Ì Y Ì

# YÍYÍ ÈTÒ ÌSÚNÁ RẸ PADÀ

## Agbára ti Ìlànà

P Ò P

GARY KEESEE

A D À

Ọ̀rẹ́ mi ọ̀wọ́n nínú Krístì,

Àdúrà wa ni pé wà rí ìdánilẹ́kọ̀ yìí bí orísun ìbùkún àti ìgbani níyànjú fún ọ. Jọ̀wọ́ má tẹ̀tì làti pín ohun èlò yìí pẹ́lú àwọn ọ̀rẹ́ rẹ, ẹbí àti àwọn ọmọ ìjọ rẹ. Aha o le kàn sí FLNfree.com láti gba àgbàsílẹ̀ àwọn ẹ̀dá míràn tókù àti fún àwọn ìdánilẹ́kọ̀ ọ̀fẹ́ ní èdè abínibí rẹ.

Ọlọrun fẹ́ràn rẹ o sì ní àwọn ètò tí ó dàra fún ayé rẹ. Ẹ̀kọ́ tí a kọ́ nípa bí a ti nṣe nínú ìjọba Ọlọ́run yí ayé wa padà sí dídára, a sì gbàgbọ́ pé yóò ṣe ohun yi kanna fún ọ!

Pẹ́lú ìfẹ́ ti Krístì,

Garry ati Drenda Keese



P.S. Jọ̀wọ́ rántí láti lọ gba àgbàsílẹ̀ lọ́fẹ̀ẹ́ lórí ìtàkùn ayélujára wa FLNfree.com láti gba àgbàsílẹ̀ awọn tókù àti ìdánilẹ́kọ̀ lọ́fẹ̀ẹ́ ní èdè abínibí rẹ!

Ì Y Ì

# YÍYÍ ÈTÒ ÌSÚNÁ RẸ PADÀ

## Agbára ti Ìlànà

P Ò P

GARY KEESEE

A D À

**Your Financial Revolution :**
***The Power of Strategy***, Yoruba. By Gary Keesee
Copyright © 2023 by Gary Keesee,

Originally published in English
Copyright © 2015 by Gary Keesee,
ISBN: 978-1-945930-14-0

Gary Keese Ministries
P.O. Box 979, New Albany
OH 43054, USA
GaryKeesee.com

This book is a FREE GIFT from Gary Keesee Ministries and is NOT FOR SALE

**Yíyí Ètò Ìṣúná Rẹ Padà:**
***Agbára ìlànà,*** Yorùbá
Copyright © 2023 nipasẹ̀ Gary Keesee

Èdè Gẹ̀ẹ́sì ni akọ́kọ́ fi tẹ̀ ẹ́ jáde
Copyright © 2015 nipasẹ̀ Gary Keesee
ISBN: 978--9729035-9-2

Ilé -isẹ́ Ìrànsẹ́ Gary Keesee
P.O.Box  979,New Albany
OH 43054,USA
Garykeesee.com

Ẹ̀bùn ọ̀fẹ́ ní ìwé yìí láti ilé -isẹ́ Ìrànsẹ́ Gary Keesee  KÌÍ ÍSE FÚN TÍTÀ

# ÌYÀSỌ́TỌ̀

Mo ya ìwe yìí sọ́tọ̀ fún ìyàwó mi, Drenda, bi ó ti se jẹ́, ìwúrí, àti ìgbàniníyànjú, àti ìfẹ́ ti ó ni si àwọn nkan tí nse ti Ọlọrun, àti tí óni fún ẹbi rẹ̀ àti èmi nà pàápa, fún àtìlẹ́yìn àti ìwúrí, lati ọdún yìí wá. Lapapọ̀, a rìi pé àlá náà wá sí mimúsẹ!

—Gary Keesee

# ÀKÒÒNÚ


**ÌFÁÀRÀ**..........................................................................09

**Orí 1:** O fẹ́ Kí Á se Kínni?.........................................................19

**Orí 2:** Ìjọba Náà...................................................................31

**Orí 3:** Ohun Ìyàlẹ́nu................................................................39

**Orí 4:** Àwọn Ìpìlẹ̀: Má Kúrò Níle Láísì Nkan Wọ̀nyì................53

**Orí 5:** Ìjẹ́ri Sí Ti Bibeli............................................................67

**Orí 6:** Gba Gbogbo Àdúrà Ní Ìfédèfọ̀..........................................75

**Orí 7:** Àpò Ìsúra.....................................................................85

**Orí 8:** Ibi Ìgbéga Tí ó Le Koko..................................................99

**Orí 9:** Ohùn Kẹ́lẹ́ kékeré Náà....................................................107

**Orí 10:** Àwọn Ìran àtì Àlá ........................................................119

**Orí 11:** Ẹ̀mi Mimọ̀ Ndún Bí Ọgá mi............................................131

**Orí 12:** Bi a ti se le Gbàdúrà àti Gba Ìrìbọmi ti Ẹ̀mi Mimọ̀..........143

# ÌFÁÀRÀ

*Yíyí ètò ìsúná rẹ padà : Agbára ìlànà* ni ò jẹ́ ẹ̀kẹta irú ìwe yìí ti a tẹ̀ jáde léra wọn.  Máárún irú rẹ ni a ó tẹ̀ síta ti yò fi kágbá gbogbo àwọn ìpàde àpérò eyí ti a se ni Albania ni ọdún 2005 ati ohun gbogbo ti a se. Ninu ìpade àpérò yìí ni mo ti gba ìtọni ti ayé mi si yí padà bákannáà.  Tí o bá ti gbọ́ nipa ìtàn yìí rí, o le ma fẹ́ lati ka ìfáárà yi ki o lọ bẹ̀rẹ̀ kíkà rẹ̀ ni orí kinni. Sugbọn ti o kò ba ti gbọ́ ọ rí, jọwọ́ jẹ́ kí nse àlàye bó ti jẹ́ fún ọ. "Ìkuku aláwọ̀ sánmọ̀ lójú ọjọ́" (Ikuuku Bulu), o le bèrè, pé "Kinni ò njẹ́ bẹ̀? Ìbérè rẹ yé mi. Nigbàti èmi nà kọ́kọ́ rìi mi o mọ ohun tin se, sugbọ́n mo ni ìmìsí  agbara Ọlọrun tó lágbára. mo mọ̀ pé ọ̀dọ̀ Ọlọrun ni o tí wa. Jẹ́ kin sọ ìtàn nà fún ọ.

Èmi àti ìyàwó mi bẹ̀rẹ̀ ìgbéyàwo wa ninú gbèsè ti a si wà ninú ipò gbèsè yi fún ọdun mẹ́sàn gbáko.  Ki ise pé a jẹ́ gbèsè nikan, bikose pé a tún pafọ̀ ninú ìyà, wàhálà àti ìbẹ̀rù lorí owò àti ìsòro owò. Lóòtọ́ a kò fẹ́ lati pa ayé ara wa lára nitorí ètò ìsúnà wa, ohun ti a se nìyí. A bẹ̀rẹ̀ pẹ́lu epo pẹtirolù láwìn, à gbàá lákọ́kọ́, titi de ori ẹlẹ́kẹwa. Nigbati àrí wípé à kò ri owó san mọ, a lọ lati lọ yá owó ni ọ̀dọ̀ àwọn àyanilówó ti wọn gbé ìdá mejìdínlọ́gbọ̀n sí mẹtàlélọ́gbọ̀n àfikún lé àdápadà wa.  A tún wá padà lọ lati tún lo kaadì ẹ̀yáwò wa lẹ́ẹ̀kan si, gbèsè wá kún gbèsè! Lopin gbogbo ìgbìyànjú ati jẹ ọ̀pọ̀lọpọ̀ gbèsè, à jẹ àwọn ilé ayánilówó mẹ́ta ni gbèsè, àti àwọn IRS ti wọn lẹ́tọ́ si àti gba ohun ìnì onigbèsè ni ẹgbẹ̀ẹ̀ẹ̀run owo dollar, àti àwọn gbèsè kekeke miràn.  À tún jẹ dọ́kita olùtọjú eyín lówó, àwọn àlágbàfọ àti àwọn obi wa ni a jẹ ni ọpọlọpọ̀ ẹgbẹ̀run owò dollar,  gbèsè wà  lórí àwọn mótò wa méjéjì, gbèsè owò ilé àti àwọn nkan miràn bẹ́ẹ̀. Ó tó àkókó kan owò iṣẹ́ ti o ba se ló gbà ni a fi ngbé ayé wa, wahala ibẹ̀ si npa mi kú lọ, To fi jẹ́ wipé nise ni àyà mi njá, ti ipayà de, ti mo wá n lo òògun ti ìrẹ̀wẹ̀sì ọkàn, ti kò le ràn mi lọ́wọ́.

Ohun gbogbo ti a ní ni o ti bàjẹ́. Bẹ́ẹ̀ na I àwọn mọ́tò wa ti ni to igba ẹgbẹ̀run màili lori wọn.  Abà kekeré ti a yá ni ọdúnrún dọ́lla ní ososù ti wọn ti kọ́ ni 1856 ibi ìkó èrè oko si ni o ti bàjẹ́. Gbogbo àwọn fèrèsé ni o ti bajẹ́, sugbọ́n ko sí owó lati fi tún wọn se, à kan rọra fi nkan lẹ̀ẹ́ àti kẹ́ẹ sibẹ̀ ni. Kódà, èyí kó si bojúmu to. Awọn koríko tún gba ibẹ̀ hù wọlé. ìyawo mi yóò rọra túnse ti yòó si dun wò. Awọn ẹni àtẹ́ẹ̀ká ti yàrá àwọn ọmọkùnrin

ti di pànti ilé ilẹ̀. Ìbùsùn ti di ohun ile ilẹ̀ bẹ́ẹ̀ náà ni àwọn àgba ìjóko nà ti di ti gbaraji ọkọ̀.

Ile ayé kò rọgbọ nigbàti o bájí ni òwúrọ̀ ojojúmọ́ ti o wá ndàmú lorí ohun ti àwọn ẹbi rẹ yòó jẹ tabi yóò mú. Ibẹ̀rú bojo wá bá ayé mi, ayọ̀ àti ìrètí wa di ìdàrúdàpọ̀, ẹlẹ́mi ni yóò làájá.. Èmi àti Drenda si ngbé ayé wa báyìí fún ọdún mẹ́san gbáko! Ní ọdún mẹsan gbáko! Mo gbọ́ ti osù kan, tabi ọdùn kan tó ba burú tán, sugbọ́n ọdun mẹsan? Lẹ́yìn ọdun mẹ́san ti wahala àti ìdààmú yìí, imọ̀ara rẹ wa ti di ti kòsí àìṣe àti sùúrù mọ.

Ni gbogbo ọdún mẹ́sàn yi, ọmọ lẹ́yìn Kristi ni wá ti a sì nlọ si ilé ìjọ́ sin nla kan ti wọn ti kọ́ wa pé òsi/ àini kì ìse ìfẹ́ Ọlọrun fún àwọn ènìyàn Rẹ̀. A máa nsan ìdámẹ́wa àti se ìfifún ni gbogbo ìgbà, sibẹ̀ ìsúná wà ko fi ohun ti Ọ̀rọ̀ Ọlọrun sọ hàn. Mo ti kọ́ ẹ̀kọ́ ninú Majẹ̀mu lailai àti lọ si ile ẹ̀kọ́ Bibeli fún ọdun kan. Èmi gan mọ̀ pe nkan kò lọ déédé nkan nsẹlẹ̀, síbẹ̀ mo si ni ìrètí pé, tobáyá nkan yòó yípadà. o dára nà, kòsí ìyípadà láàrin ọdún mẹsàn yìí. Àwọn ti ngba owó máa npè wá ni ojojúmọ, èmi ati Drenda ti fẹ́ sọ ìrètí nu.

Yàtọ̀ si àwọn nkan wọ̀nyìí àwọn onimọ̀ìsegùn tun sọ wipé mo ti fẹ́ bẹ̀rẹ̀ sí ni ààrùn àtọ̀gbẹ nitori àwọn àìlera ti mo ndojúkọ. Ko sí owó nibikankan, gbogbo káádi ẹ̀yáwó ni wọn ti fagilé, ko tún si ounjẹ ninú ile mọ. Ẹ̀ru wá bẹ̀rẹ̀ si ni bàmi ti mo si tún bẹ̀rù àti jáde ninú ile mi lọ si ibikíbi. Ìyawó mi ti ngbèro bi oun ati àwọn ọmọ yóò se gba ilé àwọn òbí tirẹ̀ lọ, o si nro wipé oun yóò si sọ ọkọ oun nu niyìí. Sibẹ̀sibè, ni àsìkò yi gàn ni ìyípadà de bá ayé mi, ti ohun gbogbo sì yí padà.

Asojú ofin kan wà ti o ti máa npè mi, ti mo ti máa sọ fún pé màá san owó na fún, ti mo sì nirèti pé má san, sugbọ́n mi o ri owó na lati fi san án. Ni owúrọ̀ ọjọ́ to tún pè mi, ko fi sùúrù sọ ọ̀rọ̀ mọ́. Óni "Oni lati mú owó na wa loniì si ọ̀tunla, bi bẹ́ẹ̀kọ̀ ma fi pánpẹ́ ofin gbé ọ nitorí owó ti o njẹ onibárà mi" Nigbànáà ni mo ti wá mọ pé gbogbo ìdíbọ́n ti dopin. Èmi kò ni owó lọ́wọ́, kódà kòsí ẹbi mi kan tí ó le yá wa lówó miràn mọ. Ninú ipò yìí, mo wa gun òkè lọ sinú yàrá ni ile kekere nà, mo fẹ̀yìn lélẹ̀ lori ìbùsùn mi, mo kígbe si Ọlọrun. Si ìyàlẹnu, lati inú ẹ̀mi mi wá, Ó dá mi lóhùn lojúkannà. Ni àkọ́kọ́, Ó ránmiletí ẹsẹ Bibeli kàn ti mo gbọ́ ti mo si kàá dáradára ni ọ̀pọ̀ ìgbà, "ìwe Filipi 4:19:

*"Sugbọ́n Ọlọrun mi yóò pèsè ní kíkún fún vovo ànìní yin, gẹgẹ bí ọrọ̀ ògo rẹ ninú Kristi Jesu."*

"Bẹ́ẹ̀ni, mo mọ ẹṣẹ Bibeli nà" Mo sọ fún Oluwa bẹ̀ mo si tẹ̀síwájú lati sọ fún pé "kò sẹlẹ̀ rí bẹ̀ ninú aye mi, kò sí àìnì mi kan ti o bá pàde." Oluwa wa dámi lóhùn padà pé, "Èmi kò ni ohunkan se pẹ̀lú ipò ìdọ̀tí ti o fi ara rẹ sí. O bá ara rẹ ninú ìdọ̀tí nitorí o ti kọ́ ẹ̀kọ́ bi a ti n se ninú ijọba mi" Ó tẹ̀síwájú lati sọ àwọn ohunkan miràn fún mi, sugbọ́n ọ̀rọ̀ ti o nsọ óyé mi: Gbèsè ki ìse ìfẹ́ Rẹ̀ fún ayé mi.

Bíótìlẹ̀jẹ́jẹ́pé mo láyọ̀ pé mo gbọ́ lati ọ̀dọ̀ Ọlọrun. Mo ni lati gbà pé mi o ti mọ́ ohun tí ó nsọ nipa ìjọba Rẹ̀. Mo kọ́ ẹ̀kọ́ Bibeli gboyè, mo si lero wipé mo mo Bibeli dáradára, síbẹ̀, o hàn gbanga pé, mo nse àsìse. Ohun àkọ́kọ́ ti mo se lẹ́yìn ti mo gbọ lati ọ̀dọ̀ Ọlọrun tán ni lati lọ wa Drenda àti ki a ronupìwàdà kúrònìnú ìdọ̀ti ti a kọ ara wa sí. Lẹ́yìn nà àwa mejejì gbàdúrà si Ọlọrun a sì ni kí o kọ́ wa bi a ti n se ninú ìjọba Rẹ̀. A tún ronupìwàdà kurò ninú gbigbáralé àwọn gbèsè àti se ìpìnnu ao ni fi ìgbẹ́kẹ̀lé wa sí gbèsè mọ bi ọna àbáyọ mọ́ ni ayé wa. Sugbọ́n, lóòtọ́, bí mo ti gboyè ninú ẹ̀kọ́ Bibeli tó, Ohun ìjìnlẹ̀ ni ìjọba Ọlọrun jẹ́. Ìgbà kan ti mo ranti ti a lo ọ̀rọ̀ ìjọba ọ̀run ninú Majẹ̀mu Titun ni ninú àdúrà Oluwa.

"*Kí ijọba rẹ dé, ìfẹ tìre ni kí a se ní ayé bí wọn ti ń se ni ọ̀run.*" (Máttiù 6:10)

A le mọ ti mọ ohun ti Ọlọrun nsọ fún wa, sùgbọ́n bi a ti se nwá Oluwa, Yóò bẹ̀rẹ̀ si ni máa kọ wa. Ohun àkọ́kọ́ ti a gbọdọ́ mọ̀ ni kinni ìjọba ọ̀run jẹ́ àti kin ni ìdí ti Ọlọrun fi lo gbólóhùn yìí. Kin ni ohun ti o ngbìyànjú lati sọ fún wa? Lẹ́yìn ọ̀pọ̀lọpọ̀ ìwádí, mo wa ri pé ìjọba ọ̀run kì íse àgbájọ àwọn èniyàn lásán. Ójẹ́ ti àgbájọ àwọn èniyàn ti wọn ngbé lábẹ́ sàkáni agbára isakoso ìjọba àti ti ọba. Kodà gbolohùn yi ìjọba ni à ntọka sí bi ìjọba ti ọba. Ìjọba ti ọba, tabi àṣẹ àti awọn òfin rẹ̀, ti gbogbo à ntẹ̀lé gẹ́gẹ́ bi ọmọ orilẹ̀-èdè ninú ìjọba rẹ̀. Àwọn Ohun ti o se kókó sími nibiyìí ni: Ijọba Ọlọrun jẹ́ ìjọba. Atipé ìjọba rẹ̀ si ni awọn òfin!

Se o ríi, mo ti wo Ọlọrun bi ọ̀pọ̀ Kristiani ti máa nse, pẹ̀lú asise ninú

òye ohun ti Ó le se. Mo ti lero pé nitorí ti ó jẹ́ Ọlọrun ohun gbogbo  ti o ba wùú ni Ó le se ni ìgbàti o ba wùú lati seé. Mo mọ̀ pé nibáyìí ninú ìwe nà o le wà sọ pé kò ri bẹ̀, sugbọ́n jẹ́ ki a tẹ̀ siwajú ná.

Nitorí pe mo gbàgbọ́ pé Ọlọrun le se ohun gbogbo.ti o ba fẹ́ ngbakúgbà ti o bá wùú, mo ti wo awọn àdúrà ti kòni èsì bi ohun ti kò fẹ́ se. Àìnidanilójú yìí sí àdúrà ni o mú mi ki sa ni ìretí pé yòó dahùn àdúra mi. Àwọn ọ̀nà ti mo máa fi gbàdúrà ni bi kin máa sunkún àti bẹ̀bẹ̀ fún àànu, pé ọ̀rọ̀ tèmi le ju ki Ọlọrun ma kiyesi mi lọ. Sugbọ́n nigbàti Ọlọrun bẹ̀rẹ̀ si ni kọ́ mi pe gbogbo ìjọba rẹ̀ jẹ́ ìjọba pẹ̀lú àwọn òfin ti a le kọ́ ati mú lò, inú mi wá dùn gidigan. Mo kọ́ pé nigbati mo wa sọ̀dọ̀ Kristi mo ti di àrolé àti ọmọ ìjọba Rẹ̀ nla.

*"Nítorínà ẹ̀yin kì íse àlejò àti àtìpó mọ́, sùgbọ́n àjùmọ̀ jẹ́ ọlọ́tọ̀ pẹ̀lú àwọn ènìyàn mímọ́, àti àwọn ará ilé Ọlọrun" (Éfésù 2:19).*

Mo wa rantí ìwe mimọ́ ti mo kà àti ròó, pé, *Mo ní ẹ̀tọ́ lábẹ́ ofin nínú ìjọba Rẹ̀! Sé bí ó ti se rọrùn tó nà nìyìí? Gẹ́gẹ́ bí ọmọ orílẹ̀-èdè ilẹ̀ Gẹ̀ẹ́sì, mi ò ní láti máa bẹ̀bẹ̀ fún àwọn ohun tí ó jẹ́ tèmi lábẹ́ ofin gẹ́gẹ́ bí ọmọ orílẹ̀-èdè nà. Mi ò nílò láti jẹ́ kí ara mi sú ú gàn ìn kí wọ́n tó le mọ̀ pé ọmọ ilẹ̀ náà ni mo jẹ́. Ibẹ̀ ni wọ́n bímisí. Bí mo ti se di àtúnbí sínú ìjọba Ọlọrun, ni mo ti di ọmọ olú ìlú ti ìjọba Rẹ̀. Tí ó túmọ̀ sí pé mo ni ẹ̀tọ́ lábẹ́ òfin lati wọlé àti sí gbogbo àwọn ànfàní tí aḳọsílẹ̀ nínú òfin ti ìjọba ọ̀run Rẹ̀.* Ayé mi yipadà pátápátá nigbà ti Ọlọrun bẹ̀rẹ̀ si ni fi hàn mi pé, Wòó, ìwọ àti Drenda , bi awọn Kristiani miràn, kò ni òyé ti Ìjọba àti àwọn òfin ti o wà ninú Ìjọba ti Ọlọrun.

Kóda, wa máa gbọ ti ọ̀pọ̀ àwọn Kristiani yóò ma paríwo pé,  "Ọlọrun ló gbàá láyè, Ọlọrun lo mọ èyí tótọ́, Ọlọrun ni o nsàkóso rẹ̀, tàbi Ọlọrun lọba." Nigbàti ẹnikan ba ndojúkọ ìsoro. Àwọn gbolóhùn ọ̀rọ̀ yìí fi hàn pe Ọlọrun ni agbára lati mu ọ̀nà àbáyọ wa àti dahùn, sugbọ́n kò fẹ̀ lati seé tabi kò ti setán lati dási ọ̀rọ̀ nà. Ìrú àgbékalẹ̀ àwọn eke ọ̀rọ̀ yìí nipa Ọlọrun fi hàn pé à kò ti mọ ìwà Ọlọrun tàbi ni òye bi  Ìjọba Ọlọrun ti se nsisẹ.

Ẹ jẹ́ ki nse àlààyé ohun ti mo nsọ. Ti o ba ni bi billiọnu kan owó dọllar

ní ile ìfowòpamọ, wàá máa sọ pé, “Mo ni billiọnu kan owó dọllar” Sùgbọ́ n kò si billiọnu dọllar ni àpò rẹ nigbàti o nsọ̀rọ̀ yìí. Dipo, bẹ́ẹ̀ pé o ni billiọnu dọllar ni ilé ìfowópamọ́ , ti o si tún jẹ́ pé, o ni lati tẹ̀lé ilànà lábẹ́ òfin ki o tó tún le gba owó nà padà sọ́dọ̀ rẹ. Bẹ́ẹ̀ nà ni Ìjọba Ọlọrun ti rí. Gẹ́gẹ́ bi ọmọ àti ara ẹbí ti Ọlọrun, àwa ni àrólé ohun gbogbo ti Ọlọrun ni, Sugbọ́n òfin àti ìlànà wà ti a duro le lórí ti o ti sọ wa di ẹniti o ni ẹ́tọ́ tẹ̀lẹ̀,

Níwọ̀n ìgbà ti àwọn ènìyàn kò ni òye ti ìjọba Ọlọrun ti wọn kò si mọ àwọn ìlànà àti òfin bi ó ti se le sisẹ, ti nkan kó ba rí bi Ọ̀rọ̀ Ọlọrun ti só, àwọn ènìyàn yóò ma wòó pé ọ̀dọ̀ Ọlọrun ni àsìse ti wá, ki se àti ọ̀dọ̀ àwọn.

Nkan kan ti mo sàwárí ni pe, fún àpẹẹrẹ; o pinnu lati fò sílẹ̀ lati orí ilé gogoro kàn , ti o kò si ni  ohun èlò ti o fẹ́ fi fò (párásútù), kòsi nkankan, sugbọ́n o ti ni lọkàn pé ti o bá ti nawọ́ rẹ dára wà le fò sílẹ̀ laiséwu.  Mo lerò wípé ìwọ náà yóò ri èsí ìwà òmùgọ̀ nìbiyìí.  ìdi ti òye yí fi yé ọ nipé ọ mọ òfin ti o rọ̀ mọ̀ júju nkan soke pé ilẹ̀ ni o nbọ̀. (Grafiti). O sì mọ pé òfin yìí ki se ojúsajú, ko si pé ẹnikan ni mo fẹ́ràn jù. o si nsiṣẹ ni ọ̀nà yi kannà ni gbogbo ìgba, o ni ti mọ àbájáde rẹ dajú. Ni ọ̀nà yí kannà, tí ò ba tanná, wa reti kí ìmọ́lẹ̀de nitori o ni òye òfin ti o rọ̀ mọ́ iná títàn. Nigbàti mo bá nlọ ninú ọkọ̀ ofurufu mo ni òye ti òfin  ki a gbé nkan sọkè. Ọkọ̀ ofurufu àti iná nṣiṣẹ nigbogbo ìgba nitorí iṣẹ wọn dúró lorí awọn òfin ti a le kọ́ lẹ́kọọ àti se ẹ̀dà rẹ̀ lati tun le pèsè ohun yi kanna ti yóò si ma sisẹ́ nigbogbo ìgbà. Ìjọba Ọlọrun nsiṣẹ ni ọ̀nà yí kanna ni ìpele ti o dajú.

*Ẹ̀yí sì ni ìgboyà tí àwa ní niwájú rẹ̀, pé bí àwa bá bèrè ohunkóhun gẹ́gẹ́ bí ìfẹ́ rẹ̀, ó ngbọ́ ti wa. Bí àwa bá sì mọ̀ pé ó ngbọ́ ti wa—ohunkóhun tí àwa bá bèrè—áwa mọ̀ pé àwa rí ìberè ti àwa ti bèrè lọ́dọ̀ rẹ̀ gbà*

—1Johannu 5:14-15

Èyí ni ìgboyà ti a ní. Ti a bá bèrè ohunkohun gẹ́gẹ́ bìi ìfẹ́ ti Ọlọrun, àwa mọ pé ó ngbọ́ ti wa, àwa si mọ pé a ò ri ohun ti a bá bèrè lọ́wọ́ Rẹ̀ gbà. Mo fi èyí da ọ lojú nitori Ọba ni o sòfin nà. Yóò si ti òfin Rẹ̀ lẹ́yìn. Nigbàti Ìwe Mimọ́ sọ pé Ó ngbọ́ ti wa, ko sọ pe Ó ngbọ́ ohùn ọ̀rọ̀ wa lásán , bikose pé, ó ntọkasi bi adájọ́ se ngbọ́ ẹjọ́ ti yóò si se ìdajọ.Adájọ ki íse ìdájọ rẹ̀

lori ìmọ̀ara rẹ̀, bikosepé o wa nipo lati ríi daju pé ó mu ki òfin na se ànfàni fun àwọn ìjọba rẹ̀ náà. Ẹniti ó ti mọ opin ejọ́ kó tó bẹ̀rẹ̀.

Èmi àti Drenda àa ri àwọn ohun tó lapẹẹrẹ ti o nsẹlẹ̀ ninú ayé wa nigbàti à wa bẹ̀rẹ̀ si ni máa se ohun tí òfin ti íjọba rẹ̀ sọ ninú ayé wa. Gbèsè kúrò lọ́run wa pátápátá, láàrin bíi ọdún meji ati àbọ̀. Awá bẹ̀rẹ̀ si jẹ ounjẹ ti o mu inú wà dùn àti àwọn ọmọ wà mẹ́tẹ̀ta àti san owó ọkọ̀ titun à si kọ́ ilé ti o wù wá lọ́kàn lati kọ́ sórí ilẹ̀ ìwọn bàtà ẹṣẹ̀ maarùndinlọ́gọ́ta (55 acres) tí a sì san owò rẹ̀. A dá ilé iṣẹ́ tara wa silẹ̀ ni ọdun nà, ti o si nmú ẹgbẹgbẹ̀rún owó dọllar wá fún wà bi èrè. A si wá lọ dá ile ìjọsin silẹ̀ ni ilu wa lati le pin pẹ̀lú àwọn ènìyàn ohun ti a sàwári nipa ijọba ti Ọlọrun. A sì wa ri wipé ọ̀pọ̀lọpọ̀ àwọn ènìyàn ni wọn fẹ́ mọ ohun ti a sàwárí ati làti máa gbé àyé rere èyí ti ìjọba Ọlọrun fi fún wà. Nitori ìròyìn ayọ̀ ti ìjọba Ọlọrun yìí, Ijọ Ọlọrun si ndàgbà àti làgbárá sii.

Bíótìlẹ̀jẹ́pé ìjọba Ọlọrun nà ni ẹ̀kọ́ ti mo nkọ wọ́n ni ojojúmọ́ ẹnikẹ́ni ti o ba tẹ́tí, mo ti pinnnu lati kọ́ àwọn ẹgbẹ́ ìsọ̀wọ́ àwọn ènìyàn kàn ti wọn o ti gbọ́ọ rí gẹ́gẹ́ bi ìrírí kan. Mo mọ́ pé ki ẹ̀kọ̀ yi to le máa fàràhan ninú ayé àwọn ti o ngbọ́ọ, wọn ni lati ni òye ti Ìjọba Ọlọrun yìí, mo sì ni lati fi àyè silẹ̀ lati kọ́ wọn àti le jẹ̀ kí òye yìí yé wọn dáadáa. Ọ̀na ti mo nrò lati gbà se ni bi àwọn ìrìrì ti mo ni bi mo ti se ndagba ninú ìjọ Methodist. Nigbàti mo wà ni ọ̀dọ́ a máa se ìsọjí ọlọ́sẹ̀ kan ni gbogbo àsàlẹ̀. Mo wa wòó pé mo le se ètò ìsọji ọlọ́sẹ̀ kan lorí èto ìsuna wà, ti a bá máa se yóò gbà wa to àsálẹ̀ ọjọ màárun. Mi o ti se ìdanilẹ̀kọ́ ti ìjọba Ọlọrun bayìí tẹ́lẹ̀, mo si nwo pé báwo ni ma ti se àgbékalẹ̀ rẹ. Sugbọn ohun ti mo nwò ni irú ipa ti ìdanilẹ́kọ ọlọ́jọ́ marun yìí ma se ninú àye àwọn ti o ba gbọ́ọ. Mo wa bẹ̀rẹ̀ si ni gba àdurà lori bi yóò ti se wáyé lati se irú ìpade yí àti bèrè lọ́wọ́ Ọlọrun fún ànfàni lati leè sée bẹ̀. Ohun ti mo nbèrè fun ni lati le kọ́ àwọn ènìyàn ti wọn o ti gbọ́ nipa rẹ̀ tẹlẹ̀.

Ni ọ̀sán ọjọ́ kan, mo salábapàdé ọ̀rẹ́ mi kan tin se ajínrere ni Albania. Gbogbo ọ̀rọ̀ ti a sọ dá lé iṣẹ- ìránṣẹ àti ìjọ Ọlọrun, kóda ohun gbogbo ti Ọlọrun nba mi sọ àti fi hàn mi nà ni à mẹnubà ni ọjọ na. Ajinrere Larry fẹ́ se ìpàdé àperò ti àgbáyé ti nse àsekágbá ti ile iṣẹ ìranṣẹ rẹ ti ọdun na ni Albania ti o si wa pè mi bi ọ̀kan lara àwọn olusọ̀rọ̀ ọjọ nà, mi o ti lẹ̀ ba sọ ohun kankan nipa èròngbà ọkàn mi, sugbọn inú mi dùn nigbàti o sọ fún

mi pe ìgbà mẹ́ta ni ma fi bá àwọn ènìyàn sọ̀rọ̀ ninú ìpadé àpérò na. Ó ni mo ni lati sètò bi ma ti wá si ìpàde nà àti àwọn ìránṣẹ Ọlọrun miran ti mo ba fẹ́ lati mu dáni wá, nitorí ni gbogbo ìgbànà Albania jẹ́ ilu ti ó salaìní. Mo gbà mo si sètò bi ma ti se lọ si ìlú Albania ni ọdun 2005.

Ọjọ́ nà kò, inu mi sì dún lati dá ẹgbẹ́ àwọn èniyàn ti wọn nsẹ̀ṣẹ̀ nkọ́ ẹ̀kọ́ nipa ohun ti a pè ni Kristiani lẹ́kọ́ nipa Ìjọba Ọlọrun. Ni igbàti mo de sí Albania, ajinrere Larry wá lati pàdé mi ni ibùdó pápá ọkọ̀ ofurufú pé ọkan lára àwọn olùsọ̀rọ̀ fun ọjọ́ nà kò ni wá torínàa kin múra silẹ̀ lati da àwọn ènìyàn na lẹ́kọ́ fún ìgbà maarun ninú ìpade nà. Èmi ti mọ̀ pé Ẹ̀mi Mimọ́ ni o nsiṣẹ ó dá mi lojú! Mo ti pese ara mi silẹ̀ fun igbà mẹ́ta tẹ́lẹ̀, kiakia mo yára gbàdúrà mo si yara kọ ẹ̀kọ́ meji miràn sílẹ̀. Mo kọ́kọ́ ni ìfura díẹ̀ díẹ̀ nipa bi àwọn ènìyàn na yóò ti se gbọ́ àti ìdahùn wọn, mo nro ipò ti ilu na wà ninú àìní àti ìwà ìbàjẹ́ ni gbogbo orilẹ̀-èdè na.

Mo le sọ pé nigbàti mo kọ́kọ́ bẹ̀rẹ̀ ipa àkọ́kọ́, wọn siyèmejì diẹdiẹ, sùgbọ́n mo tẹ̀sìwájú lati máa kọ wọn ni ohun ti Ọlọrun ti kọ́mi, pẹ̀lú rẹ mo nsọ àwọn ìtàn ti o lọ papọ́ pẹ̀lú ẹ̀kọ́ ti mo nkọ wọn, inu àwọn ènìyàn na bẹ̀rẹ̀ si ni dùn wọn nyọ̀. Nigbàti ma fi pari ẹ̀kọ́ ẹlẹkẹrin, wọn ti nrẹrin, wọn si láyọ̀ sí ohun ti wọn gbọ́, ti àwọn kan tún pariwo ninú wọn. Ó sàjèjì mo ri pé Oluwa sọ fún mi lati gba owó ọrẹ nigbati à báti bọ sinu ẹ̀kọ́ kaarún . Mo sọ pé ó sàjèjì nitori pe èmi ni mo san owó fun ọ̀pọ̀ wọn lati le mu ki wọn wà ninú ìpàde yi àti pé mo mọ pé ko si owó ni ọwọ́ wọn. Sugbọ́ n lẹ́yìn ti mo ti ronú nipa rẹ̀ tán, ni mo wa sọ pé àwọn èniyàn wọ̀nyìí ni lati fi ohun gbogbo ti wọn ti gbọ́ sinú ìse. Mi o kọ́ mọ̀ bi ma ti se sọ fún ajinrere Larry, síbẹ̀síbẹ̀, ni kiakia ni o sọ pé kin tẹ̀síwájú o si bẹ̀rẹ̀ si ni gba ọrẹ. Bẹ́ẹ̀ni, mi o gba ọrẹ fún ara mi; ọrẹ na yóò wà ni Albania nà ni fún ànfàni àwọn ìjọ .

Ipa to gbẹ̀yìn ti to bayìí, ti ise ẹ̀kọ́ kaarun, mo si nkọ wọn lọ bi o ti se le lo ìgbàgbọ́ rẹ, mo se àkàwe àwọn òfin kan ti mo ti kọ́ wọn . Ni iparí ètò ti mo fẹ́ gbà ọrẹ gbogbo ide ja ni . Ti gbogbo àwọn ènìyàn na bẹ̀rẹ̀ si ni pariwo ti wọn njó bi Ẹ̀mi Mimọ́ ti Ọlọrun se kun inu gbọngàn na. A ri àwọn ènìyàn mẹrin ti wọn dìde dúró ni waju pẹ̀lú igba ọrẹ, agbára Ẹ̀mi Mimọ́ kun inu ile nà ti àwọn ènìyàn kò si le dúró lorí ẹsẹ̀ wọn ti àwọn kan si nsunkún lábẹ́ imisí agbára ti Ọlọrun bi awọn ènìyàn ti nmú ọrẹ wọn wa

síwájú. Mi o ti ri iru ìpàdé bẹ́ ri  pàápá nipa ọrẹ gbígba!

Ajinrere Larry àti èmi nà kúrò nibi ìpade nà, a wá nsọ̀rọ̀ nipa bi agbára ìforóróyàn na ti lagbára tó àti ìdáhun àwọn èniyàn ni alẹ́ ọjọ́ nà. Nígbàtí a dé ile ajinrere Larry ni ẹ̀yìn ìpàde, Larry múra lati ka owó ọrẹ na nitorí ko ti gba iru owọ́ ọrẹ bẹ́ẹ̀ rí ti nse àpò meji ti ọ kún fún owó ọrẹ. Ìdá mẹrin ni iye owó ọrẹ ti ó má ri gbà nigbàti o bá ngba ọrẹ tẹ́lẹ̀.  Bi Larry ti tú àwọn ọrẹ inu àpo si orí tabili ninú yàrá ìgbàlejò rẹ̀, lójijì ìmọ́lẹ̀ bi ìkuuku àlàwọ bi ojúsánmọ tàn o kún gbogbo inú yàrá nà (ìkuuku Bulu), àti ìfororóyàn bi èyí ti kò ti sẹlẹ̀ ri wá sorí wà. A kò sì le se ohunkóhun ju ki a joko sórí àga lọ. Bi mo ti nwo àkójọpọ̀ owó na ni orí tábílì niwajú wà, mo se àkíyèsí òrùka ìgbéyàwó ni ààrin rẹ̀. Mo mọ̀ pé ẹnikan tí kò ni owó lọ́wọ́ ni o fi ohungbogbo ti o ni sibẹ̀. Bi mo ti ri òrùka na ni mo gbọ ohun Oluwa bá mi sọ̀rọ̀ pé.

"Mo npé ọ́ lati lọ kọ́ orilẹ̀-èdè gbogbo ni Majẹ̀mú mi ti ìbùkún ètò ìsúná, atipe gbogbo ibi ti mo ba rán ọ lọ ni màá ti sán fún ọ"

Mi o ti setán,  fún  odidi ọjọ́ mẹta ni mi o fi le sùn. Ìfororoyàn na wà ni ori mi fun ọ̀sẹ̀. Bi mo ba máa bá ẹnikan pàdé ni orilẹ̀-èdè kan ni  ma ti mọ̀ nipa ìfòróróyàn ni. Bíótìlẹ̀jẹ́pé ọrẹ nà wà fún àwọn ìjọ Albanian náà ni, Lẹ́yìn ìgbà ti mo dele tán ajinrere Larry pè mi ó ni Ọlọrun ni ki oun fi òrùka na ranṣẹ si mi. Inú mi dùn, Bíótìlẹ̀jẹ́pé mi o sọ ohunkohun fun Larry nipa ifẹ́ mi lati ni òrùka nà, ó gbọ́ ọ lati ọ̀dọ̀ Ọlọrun lati fi òrùka na rànṣẹ si mi. Mo fẹ́ kin ni òrùka na bi ohun ìrántí ohun ti Oluwa sọ fún mi, àti pé loni yìí mo ti mọlé ògiri mi.

Nígbàti mo padà si ile ni Ohio, pasitọ kan ti nse ọ̀rẹ́ Larry ti nse pasitọ ìjọ kekere kàn ni Utah, gbọ́ ohun ti o sẹlẹ̀ ni Albania o si rànṣẹ́ simi lati wá bi mo ba le wá. Ibi àyè ti àwọn Indià fi silẹ̀ sapákan ni o tin se iṣẹ ìránṣẹ rẹ bi olùsọ́- àgùtàn  o wá ni àwọn èniyàn na se àlaíni púpọ̀. O ni àwọn ọmọ ìjọ oun ko ju ọgọ́fà lọ,  sugbọ́n mo sọ fún pé ó dára bẹ́ẹ̀ na; pé mo nbọ̀.

Mo si se ìdánilẹ́kọ́ ni ẹ̀maàrun bi mo ti se ni Albania. Mi o ri ìkuuku bulu ni ibẹ̀, sugbọ̀n àmì ìfòróróyàn ọjọ́ nà ni àgbára.

Ọrẹ ti à wa gbà ninu ìsin na  jẹ́ ti ilé iṣẹ ìránṣẹ mi, Nígbànà ni mo palẹ̀ bagi owó ọrẹ na mọ́, mo si padà si Ohio. Bi mo sì ti dé ile iṣẹ mi mo gbé àpò na le akọ̀wé mi lọ́wọ́ lati ka owó ọrẹ nà ki o sì ko lọ si ilé ìfowópamọ́

fún mi, leyìn igbànà mo lọ lati lọ jẹun ọ̀sán . Nigbà ti mò njẹun lọ́wọ́, ẹ̀rọ ìbanisọ̀rọ̀ mi dún, mo si ri pé akọ́we mi ni o npè mi, nigbà gbti mo gbà ìpè nà mí o tilẹ̀ gbọ́ ohùn ẹnikankan, síbẹ̀. bi mo ti fẹ́ lati paá mo ro wipé mo gbọ́ pe ẹnikàn nsunkún, mo ni, "Tracy?" Tracy damilóhùn, ò ngbiyànju lati mu ara rẹ bọ sipò "pasitọ," "kinni nkan ti o sẹlẹ̀ ni Utah pẹ̀lú owó ọrẹ yìí?" "Kinni o rí? Kinni ohun ti o sẹlẹ̀ sí owó nà?" "O dára," ni o sọ, "nígbàti mo sí àpo owó naà ti mo ni kin dáa sórí tabili lati káa, lojijì, ìfàmi òróró Ọlọrun pọ̀ to bẹ̀ gẹ́ ti mo fi npora mọ́lẹ̀. Nigbàtí àkọ̀wé keji sáré wá, lati wá wo ohun tí ó sẹlẹ́, agbára Ọlọrun tún kọlu oun nà bakannà! Kinni o wá sẹlẹ́ si owó nàà, Pasitọ̀?" Mo wá sọ ohun ti o sẹlẹ̀ ni Utah fún un àti bi ìfàmì òróró yàn náà ti ni agbára tó nibẹ̀ bi mo ti se ngbà owó ọrẹ, sùgbọ́n ju gbogbo rẹ̀ lọ, mo ro pé nkan mi tún sẹlẹ̀ ni. Mo ni lati gbà torí inú mi dùn nipa àwọn nkan ti o sẹlẹ̀ lọ́wọ́ nitori mi o ti gbọ iru rẹ̀ tàbi rí ohun ti o jọ báyìí rí. Lótítọ́ mi o ni òye irú nkan yi rí, o han gbangban pé, ìfòróróyàn lati inú ìpàdé wa wà lorí owó ọrẹ na! Lootọ!

A ti wá bẹ̀rẹ̀ ohun ti à npè ni ìpàdé àpérò yíyí ètò ìsúná rẹ padà ni gbogbo orilẹ̀-èdè àgbáyé, ninú àwọn ìjọ nla tàbi àwọn ìjọ kekeke, nibigbogbo ti àwọn ènìyàn bá gbe wà lati tẹtí gbọ́. Bíótìlẹ̀jẹ́pé a ri ìkuuku bulu ni àwọn ìpàdé kan, ìfòróróyàn nà si máa ni agbára. Bi ni Albania àti owó ọrẹ lati inu ijọ Utah àti India, ìfòróróyàn tun wà lorí owó ọrẹ nà tìkalárarẹ̀. Mo sakiyèsí pé lẹ́yìn ìpàde nà àti owó ọrẹ ti a ti kà tán, bi o bá le mu ẹyọkan dani ni owò na ara rẹ kòni balẹ̀ mọ́. wa máa gbọ̀n ni lábẹ agbára ìfòróróyàn ti Ẹ̀mi Mimọ́. Ohun miràn ti mo tún se àkiyèsí ni ti owó tàbi sọ̀wédowò yàtọ si ara. Gbogbo wọn kòsí ni ìpele kan na ni ti ìforóróyàn tó wà lorí wọn.

Lẹ́yìn ìgbànà mo wá mọ pé èyí ni èsí ìgbàgbọ́ ti à fihàn ninú ọrẹ ti onikalukú. Aláragbàyídá!

*Ètò ìyípadà ìsúná rẹ ní sísè ntẹ̀le* ti àwọn ìwe marun wọnyìí ti dúrò fun ìgbà marun ti ìdanilẹ́kọ́ nà ti ètò yiyi ìsúna rẹ padà ni èyítí mo kọ́kọ́ se ninú ìpádé Albanian. Lóòtọ́, àwọn ìwe wọ̀nyìí si tún fẹ̀ si jù ìpàdẹ̀ àkọ́ kọ́ iru rẹ̀. Mo si gbàgbọ́ pé bi o ti se bẹ̀rẹ̀ lati máa kà nipa Ìjọba Ọlọrun ti èmi àti Drenda ti se kàá ti a si ni, yóò yí bi o ti se nri gbogbo àwọn nkan padà bi o ti se fún àwa ná. Ìwe yìí, ẹlẹ́kẹta irú rẹ̀ ni àkọlé njẹ́ *Ọrọ̀ nípasẹ*

*Ẹ̀mí Mímọ́* nigbà ti mo kọ̀ wọn ni Albania. Mo gbàgbọ́ pé gbolohùn na si jẹ́ òtitò àibẹ̀ lonìí.  O má jẹ̀ ètè ti Ẹ̀mi mimọ ni yóò mu orí rẹ yá lati mú  ọ serere. Mo si lero pé nipṣẹ ìwe yìí wa ri kọ́ bi Ẹ̀mi Mimọ se nsisẹ lorí ilẹ̀ àyé lati le mú gbogbo àwọn ìlàna  yóò fi kọjá.

ORÍ KÍNNÍ

# O FẸ́ KÍ Á SE KÍNNI?

Nígbàtí mo kọ́kọ́ padà si ilé lati Albania, mo dọ̀tí gàn. Súgbọ́n ipa ohun ti Oluwa ti se ninú ayé wa àti pé bí Óti sọ fún mi pé kin mú nkan yìí lọ si gbogbo orilẹ̀-èdè gbogbo jẹ́ nkan ti o lágbára ti díẹ ti ko se kọ̀ ninú ẹ̀mi mi. Àwọn orilẹ̀-èdè? Èmi náà ni ẹniti ó sọ fún Drenda nigbàti a ṣẹ̀ṣẹ̀ se ìgbéyàwó pé mi o ni lọ sí ìrìn àjò kankan, bẹ́ sì ni mi o fẹ́ lati lọ ìrìn-àjò ti iṣẹ ìhìnrere sí àwọn orilẹ̀-èdè miràn. Sùgbọ́n Ọlọrun ni àwọn ètò miràn, lóòtọ́. O yẹ kín lọ si gbogbo àwọn orilẹ̀-èdè, sùgbọ́n bi báwo? Mo ni oko-òwò ti o wà káàkiri àti ìjọ Ọlọrun ti mo ti nsiṣẹ̀, àwọn ẹbi mi àti ọ̀pọ̀lọpọ̀ àwọn ojuse miràn ti o wà nilẹ̀ fún mi lati bójútó ni United States. Mi o tilẹ̀ mọ̀ bi o ti se le se ṣe fún mi lati máa lọ si àwọn orilẹ̀-èdè miràn. Sugbọ́n Ọlọrun ètò kàn, èyí ni kò ni gba kin máa lọ si ìrìn -àjò kiri, èro ti mi o ti rò tàbi gbéyẹ̀wò rí, ti mi o tilẹ̀ ronú nipa rẹ̀—telifisọ̀n.

Drenda àti èmi kò tilẹ̀ mọ nkankan nípa telifísọ̀nu. Koda ni àsìkò kan à kò ti ma gba ohùn àti ìsin wà silẹ̀ sinú fánrán. Sùgbọ́n Ọlọrun wá bẹ̀rẹ̀ si ni fi hàn wá, àwọn ohun tin bọ̀ àti bi a o ti se, awá nwòó bi a o ti se bẹ̀rẹ̀ ètò lorí tẹlifísọ̀nu. Ohun àkọ́kọ́ ti mo rí nipé yóò gba ọ̀pọ̀lọpọ̀ owó lati le seé ti tẹlifísọ̀nu nigbàti à sí gbogbo owò ti yóò na wa papọ̀ ó tó ẹgbẹ̀rúnlọ̀dúnrún pọ́ùn ti a o fi bẹ̀rẹ̀ ni ọdun àkọ́kọ́ lori Tẹlifísọ̀n. Mo fẹ́ sọ fún ọ pé o kọ dáyà jámi bi etò lorí tẹlifísọ̀n ti se wọ́n tó. Nkàn tí ó wá sẹlẹ̀ ni pe lọ́wọ́lọ́wọ́ nigbànàà ìjọ sẹ̀ṣẹ̀ nkọ́ gbọ̀ngbàn titun ni ile ẹ̀kọ́ gigà lọ́wọ́ ni kòsí owò nilẹ̀, ti à le fi san owó fún èto ti Tẹlifísọ̀n. Ìdi sì nìì ti mo fi sọ fún Ọlọrun pé kò sí owó nilẹ̀ lati fi bẹ̀rẹ̀ ètò nàà báyí. Mo ránti pé Ọlọrun gbà fún mi ó wá sọ fún mi pé, "Ó dára, Ìdì siniyí ti ìwọ àti Drendà ni ẹ o san owò na.

Lati sọ pé, o já wa láyà sì kéré, pàápa nigbàti a nsiṣẹ ti o le ni milliọnu mẹfà si meje owó dọllar lọ́wọ́ lati fi kọ ilé ìjọsin wa. Gbàgbọ́ pẹ̀lú mi, iṣẹ àkànse kíkọ́ ibi ti a wà yi jẹ́ ìgbésẹ̀ ìgbàgbọ́ ti o ga ti o ngbà gbogbo owó ti o nwọ ọwọ́ wa, èmi ati Drenda ti ná owó ti o lé ní ẹgbẹ̀rún láàdọ́talérúgba pọ̀ùn sí iṣẹ àkànse nà, ati ni àkòkò ti à si nsọ yìí, owó kò fi bẹ́ẹ̀ wọlé mọ. Lati wá fi ẹgbẹ̀rúnlọ̀dúnrún pọ̀ùn miràn kún, ninú ọdún yìí kan na, o dàbi ohun ti kòní séese.

Mo mọ̀ pé inú ìrìn-àjò ti mo wà yi ti Oluwa ni, Ó si ti sèlérí lati pèsè owó fún ohunkóhun tí On bá rán mi lati se, ìro ohùn yì sì ndún ninú ẹ̀mi mi. Sugbọ́n sibẹ̀, ni ìwòye ti ènìyàn, bi mo ti nwo iye ti owó na jẹ́, mi o ti lẹ̀ ri ọ̀nà Kankan bi èmi àti Drenda ti se le ri irú owó nà san tin se ẹgbẹ̀rúnlọ̀dúnrún pọ̀ùn lorí ohungbogbo miràn ti à nse.

**MO MỌ̀ PÉ ỌLỌRUN JẸ́ OLÓTÍTỌ́ SÍ Ọ̀RỌ̀ RẸ̀, MO SÌ MỌ̀ PÉ MO NI LATI GBE ÌGBÉṢẸ̀ ÌGBÀGBỌ́, NIGBẸ́KẸ̀LÉ NINÚ RẸ̀ LATI FI OHUN TÍ MÀÁ SE HÀN MI**

Mo mọ̀ pé Ọlọrun jẹ́ olótítọ́ sí ọ̀rọ̀rẹ̀, mo sì mọ̀ pé mo ni lati gbé ìgbésẹ̀ìgbàgbọ̀, ni ìgbẹ́kẹ̀lé ninú rẹ̀ lati fi ohun ti màá se hàn mi. O wù mi lati sọ fún ọ pé mo ni ìdanilójú mi ò si se àniyàn kankan lori àwọn ìpinnu wọ̀nyìí, sugbọ́n kò ri bẹ̀. iṣẹ ti o nlọ lọ́ wọ́ ninú ijọ ni o ngba gbogbo owò ti o nwọle. Gbogbo owó ti mo ni nà ni ati lò lati san ẹgbẹ̀rúnláàdọ́talérúgba pọ̀ùn ti mo ti sọ, àti àwọn nkan miràn ninú ìṣẹ́ mi ni o nilò owó bakanna ninú ọdún yìí. Ko ti ẹ̀ si owó kankan nilẹ̀ lati fi bẹ̀rẹ̀ ètò ti tẹlifísọ̀nu ti nse ẹgbẹ̀rúnlọ̀dúnrún pọ̀ùn!

Èmi ati Drenda ti sètò fún ìsinmi ọlọ́ṣẹ̀ meji ti a fẹ́ lọ se ni Hawaii, ti mo ba sì ti wálé ni o yẹ kin fọwọ́ si ìwe àdéhùn lati bẹ̀rẹ̀ ètò ti ori tẹlifísọ̀nu.  ni otitọ́ mo ngbàdún Hawaii, sugbọ́n pẹ̀lú ohun ti o wà nilẹ̀ lati fún mi lati se ti mo ba padà sile, ko se gbé kúrò lọkàn, pàápa owó ti tẹlifisọ̀nu ti o wà nilẹ̀, mi o ti gbáradi lati se ètò yìí rara, lati ma bá ọ̀pọ̀lọpọ̀ ẹgbẹgbẹ̀run àwọn ènìyàn sọ̀rọ̀ ninú ìpade kàn lati inu tẹlifísọ̀nu. àyà mi kàn njá ni.Pẹ̀lú ohun gbogbo ti mo nro lori àti ẹ̀mi mi, mo ba ẹ̀mi ẹ̀rù wí lorí àwọn ìpinnu mi.

Bótilẹ̀jẹ́pé, mo mọ́ pé mo ti gbọ́ lati ọ̀dọ̀ Oluwa, mo si tún sọ pé kòsi owó. Oko -òwò mi nà ti mọ̀ pé kòsí owó nilẹ́ bayí, mi o ti lẹ̀ ri bi nkan yi

yóò ti se e se. Bẹ́ẹ̀ni, o ndẹ́rù bàmi, bẹ́ẹ̀ si ni  àìgbàgbọ́ ni. Mo mọ̀, ẹ jẹ́ ki nsọ òótọ́ fún yin. Mo mọ̀ pé ó yẹ kin dúró ninú ohun ti Ọ̀rọ̀ Ọlọrun sọ kin si gbojú kúrò ninú àwọn ohun ti mo ni, ki nsì ma wo òrùka yẹn. Ó ti sọ̀ pé On o san owó nà! Ni àkókò yi owó idẹ kan wà ninú àpo ọrẹ wa, bi o tìlẹ̀ jẹ́ pé mi o ti rí owó idẹ ri sááju àsikò yìí. Bi mo ti mú dání ni Oluwa bami sọ̀rọ̀ pé "gẹ́gẹ́ bi mo ti fi han Peteru ibi ti yóò ti rí owó lati san owó orí rẹ́. Ma sì fi hàn ọ́ ibiti ìwọ nà yóò ti rí owó san fún ètò lorí tẹlifísọ̀nu."

Mo si mú owó idẹ nà dání pẹ̀lú mi lọ si ibi ìsinmi ti a lọ se ni Hawaii, mo si nrìn yíká ètí okun bi mo se ngbàdurà pẹ̀lú owó idẹ na ni ọwọ́ miti o si nrán mi létí pé Ọlọrun ti yànjú ti tẹlifisọnu. Ti mo ba lọ si eti òkun lati lọ gbàdúrà, àwọn nkan ti mo ma se niìyì, mà gbàdúrà ninú ẹ̀mi fun igbà diẹ, ma si wa ni ifọ̀kànbalẹ̀ àti fọwọ́sí àdehùn ti iṣẹ orí ìmóhùnmáwọrán. Máà si ma padà lọ si ile, sugbọ́n mi o ni ti rin tó ogún si àdọ́ta ìbùsọ̀ ti ọkan mi yóò tun ti má ro pé kin ni ohun ti o fojú ri ti o le san àdurú owó na. Ohun ti o si hàn ni pé a kò ni owó nà, à kò si mọ̀ bi à ti le seé tẹlifisọnu, a kò ni àwọn ohun èlò irinsẹ́ kankan, gbogbo àtòjọ rẹ si wà nilẹ̀. Súgbọ́n ninú ẹ̀mi mi, mo si gbọ́ ohun ti Oluwa sọ fún mi ni Albania, pé ohunkóhun ti o ba rán mi lọ látise, On o san owó rẹ̀ fun un. Lati inu osù Karun ni à ti wà lẹnu rẹ̀, àti pé nitóòtọ́, mo ni lati ni ẹgbẹ̀rúnlọ̀dúnrún pọ̀ùn ki ọdun yi tó parí lati le se nkan yi, ti o wa dabi òkè nla lati gùn.

Bẹ́ẹ̀ nà ni ẹ̀mi ẹ̀ru nà nba mi sọ̀rọ̀,ti ndán mi wò bóyá ma duró lorí ohun ti Ọlọrun ti ba mi sọ. "Ìwọ na ni o ndáwa lẹ́kọ́ lorì ètò ìsúná wa, bawo ni yóò se wá ri nigbàti ìwọ pàápá kò le san owó tó yẹ kí o san?" Ma tun padà lọ si etí odò lati lọ gbàdúrà ati tun èrò inú mi se si ohun ti Ọ̀rọ̀ Ọlọrun sọ tító ọkan mi yóò tún fi balẹ̀ nipa rẹ̀. Ti mo ba padá matún lo ma jijakadì ninú ẹ̀mi àti ọkàn mi lori ọ̀rọ̀ yií fún bi ọ̀se kan tító di ìgbà ti mo tó mọ̀, pé gbogbo rẹ̀ ni yóò dára, ìbẹ̀rù ko ki le mu awọn èrò ti ó lòdì wá sinú ọkàn mi mọ́. Èmi àti Drenda ko si mọ ibití owó nà yóò ti wá, sugbọn a mọ dájú pé a gbọ́ ohùn Ọlọrun. Torinà nigbati mo padà de ile mo lọ lati fọwọ́ si ìwe àdehun nà, bẹ̀ ni a si bẹ̀rẹ̀lati mọ ohun ti a fẹ́ se lorí tẹlifísọ̀nu.

Si ìyàlẹnu nipa ọ̀rọ̀ owò sísan, arakùnrin kan pè mi lati Albania, ti mi o mọ̀, ni bi àsìkò diẹ ti a fẹ́ lọ fún ìsinmi ni Hawaii pé on ri ìwe mi kan ti mo kọ nipa ètò ìsúná oun si nifẹ́ si gan ni, niàsikò yìí èmi nìkan ni o nse

ìwe nà ati tẹ̀ẹ́ jáde, mi o si tàá ni ibikankan ju ilu mi na lọ. Sugbọ́n o dà bi wipé ọ̀kan lára àwọn osiṣẹ mi kan gba ìsinmi lọ si Atlanta o wa bá ọkunrin yi pade ni pápá ọkọ̀ ofurufú ti wọn sì ntàkurọ̀sọ nipa ìṣẹ ti o nse, osisẹ mi yi si ní ìwe mi yi lọwọ́ rẹ̀ ti o wa fún arakunrin yìí nigbati wọn fẹ́ pinyà.

Lẹyìn igbàti o ka ìwe nà tán, o ni ìwe nà dùn mọ́ oun ninú ó si fẹ́ lati ba mi sọ̀rọ̀. A jọ sọ̀rọ̀ fun igba pípẹ́, o wa sọ fún mi pé ajinrere arìrìn -àjò ni oun nse, ti afojúsùn òun si jẹ́ lilọ si àwọn orilẹ̀-èdè káàkiri fún isọji. Ó bi mi léérè pé se a le wá bi a ti se le pàdé, mo wa sọ fún pé èmi nà yóò wà sí Atlanta ni osùkan si ìgbàti a à yìí fún ìpade, tí yóò wáyé lẹ́yìn ìsinmi. A ti gbà làti pàdé. Nigbàti a ri ara wa tán à sọ ọ̀pọ̀lọpọ̀ ọ̀rọ̀. Mo si gbàdún lati gbọ́ gbogbo àwọn ìtàn ìṣẹ ìyanu àti àwọn ewu ti o nkojú rẹ̀ ni ọ̀pọ̀ ìgbà ti o bá wà ni ìrìn -àjo. Sùgbọ́n ohun ti o mú wa pàdé nà ni àkòrí ti ìsúná. Ohun ti o yàá lẹnu jùlọ na ni ìtàn mi àti bi mo ti se jáde kúrò ninú gbèsè.

Nínú ọ̀rọ̀ wà, ó sọ fún mi pé oun ṣẹ̀ṣẹ̀ padàde lati Charlotte ni, nibití wọn ti gbàá ni àlejò lori ètò kan lorí tẹlifísọ̀n, ti o si ri wipé ètò lori ìsúnà ti mo fẹ́ lati se yóò jẹ́ ìtàn nla kan ti yóò si dára lati fi hàn ninú ètò wọn yìí kannà. Óni oun yóò fi ìwe tèmi nà ránṣẹ si wọn àti ki le tun mọ̀ nipa èmi nà. Ohun gbogbo ti o nsẹlẹ̀ na nyàmilẹ́nu. Èmi o ti gbọ́ nipa ètò orí tẹlifisọ̀nu ti o nsọ̀, sugbọ́n o dajú, bi ọ̀sẹ̀ diẹ lẹ́yìn igbànà, mo gbà ìpè lati ọ̀dọ̀ oludarí ètò na, o bèrè boya mo fẹ́ lati kópa ninú èto ori tẹlifísọ̀nu na. Ọkan lára ohun ti wọn nbèrè ni pé ki o ni ohun ti o fẹ́ ki wọn gbé sórí áfẹ́fẹ́. Mo wa sọ fún wọn pe mo ni ohùn ti mo ti ká sìlẹ̀ lori ìdánilẹ́kọ́ “Yíyí Ètò Ìsúná Ara Ẹni Padà maarun CD. Wọn ni ó ti dára bẹ́, gbànà ni a wá se àdehùn lorí lori owó ti ma fi CD fún wọn. Mo fi fún wọn ni ìye owò aláràtúntà ati ni pipèsè rẹ ni ìye kanna ni. Mo fi èrè diẹ silẹ̀ fún iṣẹ iranṣẹ wa. ìyàlẹ́nu ni, pé ètò na yọrí sí rere, à sì wa ta ẹgbẹgbẹ̀rún àwọn CD na. Eyí nikan mu ọ̀pọ̀ owó jáde wà fún ìṣẹ ti à fẹ́ se lori tẹlifisọ̀n lati ibiti à kò tilẹ̀ mọ nkankan nipa rẹ̀ nigbàti à nfọwọ́si ìwe àdehùn na.

Nkan miràn ti o tún yàmilẹ́nu ni ti arakùnrin kan ninu ìjọ́ wa, ti o wá sinú ìjọ laini owó lọ́wọ́ ti wọn fẹ́ lé jáde ni bi ọdun melokan sẹ́yìn tọ̀ mi wá pé oun fẹ́ rànwálọ́wọ́ àti san owó fún èto ori tẹlifísọ̀nu wà. O ti nfi àwọn ẹ̀kọ́ ti o ti kọ́ àti gbọ́ nipa ìjọba Ọlọrun sinú ìse, kò si tòsì mọ́. Ó si fi

ọgọ́fàẹgbẹ̀rún pọ́ùn sílẹ̀ fún ìṣẹ ìranṣẹ ti ori tẹlifisọ́nù!

Nígbàti à ka gbogbo owó CD ti a tà papọ̀, àwọn ẹ̀bùn ti àwọn ọ̀rẹ́ àti ìjọ Ọlọrun fún wà àti àwọn ẹ̀bùn to wọlé èmi àti Drenda ko nilò lati tun fi owó wa kún owó ọdun kan ti à san fún tẹlifísọ̀nu mọ rárá. Ọlọrun jẹ́ ọlọtítọ́ si Ọ̀rọ̀ Rẹ̀. Óni On yóò san owó nàà o si se bẹ́ẹ̀. Bayìí , ìdaji ninú rẹ̀ ti yanjú, sugbọ́n o tun ku ìsoro kan ti o dabi pe o wúwo. Bi mo ti sọ tẹ́lẹ̀ sáájú pé, èmi kò mọ nkankan nipa tẹlifísọ̀nu!

Wọn fiwe ìpè pé Drenda si ibi ipàdé àpérò àwọn obinrin ni ibiti àwọn obinrin ti kó ara wọn jọpọ̀ si ni àrin àkókò ìpàde. Iyì nla ni pé wọn pe Drenda si ìpàde nà, ara rẹ sì yá lati lọ. Lẹ́yìn ti wọn ti parí ìgbà ti àkọ́kọ́, ti Drenda si joko lati jẹ ounjẹ ọ̀sán, arabinrin kan si joko tìí lẹ́gbẹ, wọn o ti bá ara wọn pade rí, lẹ́yìn ti wọn kí ara wọn tán wọn sọ̀rọ̀ diẹ nipa ara wọn, arabinrin na wá bèrè pé" Se pé o máa nsetò lorí tẹlifisọ̀nù? Drenda ní "Rárá, sùgbọ́n ati nronú nipa rẹ̀" Arabinrin na wá dálóhùn pe, "Ti o ba jẹ́ wipé ẹ̀ nse é, pé ẹni yi, o le ràn yín lọ́wọ́" Drenda kọ nọnbà àti Ímelii eyi ti àrabinrin nà fún un o si fi sinu àpamọ́wọ́ rẹ̀.

Lẹ́yìn bi ọ̀sẹ̀ melo kan ti o ti padá si ile, o ti gbàgbé nipa gbogbo ohun ti wọn sọ̀ nipa ìwe pélébé ti o fi sinú àpamọ́wò rẹ̀ nà,. Sùgbọ́n ni alẹ́ ọjọ́ kan o tẹ àtẹ̀ránṣẹ si àràkunrin nà lati gbọ́ ohun ti ó fẹ́ sọ. Ó dáa lóhùn dáadáa, o ni ki ó fi CD ti *yíyí ètò ìsúná rẹ padà* tí a ti se sílẹ̀ ránṣẹ sí òun, ti o sì se bẹ́ẹ̀. Lẹ́yìn ọ̀sẹ̀ kan igbákejì rẹ̀ pe ó ni àrakùnrin nà nifẹ́ si i, o si fẹ́ ki àwọn pàdé ni ibi ìpàde àpérò ọlọ́dọdún ti àwọn Àgbóhùn ẹ̀sin sáfẹ́fẹ́ ní orilẹ̀-èdè, ti kò ju ọ̀sẹ̀ melo si ìgbànà lọ. A si sọ fún pe ào rírа nibẹ̀.

Èmi àti Drenda ni a lọ́ si ibi ìpadé nà, ara wa kò tilẹ̀ balẹ̀ rárákì ìpàdé nà to bẹ̀rẹ̀. Mo si ṣẹ̀ṣẹ̀ ra kóótù dúdú kan nitorí ìpàdé na, nitori èmi o mọ ohun ti o le sẹlẹ̀. Ó ti sọ fún wa lati pàde rẹ̀ ninú yàrá kan ni hotẹ́ẹ̀lì lati le jọ jíròrò lorí tẹlifísọ̀nù.

Bi a sì ti nlọ sinú yàrá na ni mo sàkiyèsi pe nise ni à nlọ si òkè sí ìsàlẹ̀ ni àimoye ìgbà ki a to wá kan ilẹ̀kùn yàrá kàn, ki a le farabalẹ̀ diẹ. Iyalẹ́nu ni o jẹ́ fún wa nigbàtí a wọ inú yàrá na ti a sibá gbogbo awọn ti ènìyàn ti wọn nretí wa lati bá wa sọ̀rọ̀. Wọn ti to àga silẹ̀ yípo, èmi àti Drenda wa jóko kọjú sí wọn. A kò ti ba ẹnikankan ninú wọn pàdé rí, gbogbo wọn ni o mura dáradára bi akọ́ṣẹ́mọṣẹ́.

Akọ́kọ́ bẹ̀rẹ̀ si ni sọ àwọn ọ̀rọ̀ diẹ, nigbàti o yá wọn bẹ̀rẹ̀ sí ni bèrè àwọn ìbérè nipa ohun ti a fẹ́ se nipa ètò ti tẹlifisọ́nu wa. Mo sit un le ránti ìbérè ti wọn kọ́kọ́ bi wá " Tori kinni ẹ se fẹ́ sètò lorí tẹlifísọ̀n?" Lótítọ́ mi o ti mọ̀ọ́ ni ìgbà nà, gbogbo àwọn ènìyàn ti o jókòó ninú yàrá nà ni wọn jẹ́ ọ̀gá ni ìpele ẹnu iṣẹ wọn ni orisirisi ẹ̀ka ti wọn ti nsiṣẹ́. Ẹniti à ti jọ sọ̀rọ̀ tẹ́lẹ̀ na wà níbẹ̀, bẹ si ni àwọn ti o ngbé iṣẹ jàde, àwọn ti o nta ọjà wọn àti àwọn ènìyàn miràn, gbogbo wọn ni o wà nibẹ̀ ti wọn nbèrè àwọn ìbérè ti o o le koko. Ninú gbogbo rẹ̀ sá, mo mọ pé ìpàdé na lọ bótiyẹ. Àwa duro bi a ti mọ, a kò gbìyànjú lati tẹ́ ẹnikẹ́ni lọ́run dandan, a kàn nsọ ìtàn ara wa ni ohun ti Ọlọrun ti se fún wa. Ó dabi pé gbogbo wọn ni ìran àti ìfẹ́ wa ti a nse àti sọ tẹ́lọ́rùn wọn si sọ fún wa pé àwọn yóò pè wá padà ni àìpẹ́ lati tun le jiròrò lori ọ̀rọ̀ nàà si.

Ni bi ọ̀sẹ̀ melo àtún sọ̀rọ̀, ni àsìkò yi, ni à se ìpinu lati tẹ̀síwáju lori àwọn eróngbà wa ti ìgbóhùnjáde lorí afẹ́fẹ́. Asikò yi gan ni à pinnu lati se fíímù yìí ni ilé, ti arakùnrin ti Drenda bá sọ̀rọ̀ wa bèrè pé se a pàdé ni ilé wa fun ìjíròrò to kàn. Ó fẹ́ lati wá wọ ile wà boyá o le see sé iṣẹ́ nà.

Ọjọ́ nà kò ti yóò wá ài ilé wà, gbogbo wa jọ jókòó lati sọ̀rọ̀. Tití àbẹ̀wò yìí fi wáyé, mi o ti mọ ohun púpọ̀ nipa ìtàn rẹ̀ ninú iṣẹ́ tẹlifísọ́nù, Obinrin ti Drenda salábápàdé ni ó fún un ni nọmbà. Sugbọ̀n bi a ti jọ jokòó papọ̀, o bẹ̀rẹ̀ si ni sọ fún wa gbogbo àwọn ètò/eré ti o ti se lorí tẹlifisọ̀nu àti èyí ti o nse lọ́wọ́. Gbogbo ilé ni wọn ti mọ̀ọ́! Mo sáà jókòó síbẹ̀ tìyanu tìyanu, Ọlọrun, báwo ni o ti se mú ọkùnrin yìí wa lati Los Angeles sinú ile mi kékére yi, ni àwọn ọ̀nà ti o dọ̀ti ni orilẹ̀-èdè yìí ni ààrin ti kòsí nkankan? Ósi gbà lati se ètò ti o péye fún wa, ya àwòrán rẹ̀, se àtúnse rẹ̀, àti tún gbée jáde ni owó pọ́kú. Gbogbo wá gbà lati se yíya àwòrán nà ninú ilé wa, ninú yàrá ìgbàlejò wa, lati bẹ̀rẹ̀.

Ni ọjọ́ ti a fẹ́ bẹ̀rẹ̀, má jẹ́ kin tàn ọ́ jẹ nise ni gbogbo ara mi bẹ̀rẹ̀ sí ni gbọ̀n. Bi mo ti sọ pé èmi kò ni ìrírí kankan nipa tẹlifisọ̀nu. Èmi kò mọ bi wọn ti ngbétò kalẹ̀, mi o si ti sọ̀rọ̀ si kámẹ́rà rí, nise ni gbogbo rẹ̀ jẹ́ titun lójú mi: Inú mi dùn gàn pé mo ti fẹ́ gbé ìtàn ti ìjọba Ọlọrun jáde si ibi gbogbo, sùgbọ́n tẹlifísọ̀nu tun jẹ́ ohun kan ti ó ndẹ́rù bà ayé mi ti mo ni lati ségun rẹ̀.

Lati mu ki o tún wa burú síi, ni ìsẹ̀lẹ̀ kan ti ó bani ninú jẹ́ ti o sẹlẹ̀ ni ọjọ́

**" INÚ ẸNIKAN HA BÀJẸ̀ NINÚ YÍN BÍ? JẸ́ KÍ Ó GBÀDÚRÀ"**
**—JAKỌBU 5:13**

ti a fẹ́ gbohùn sí teepù ti ó wá mu ki o lekoko. Ẹniti wọn rán wà lati wá bá wa ya fiimú ti yóò gbàá ni ọ̀sẹ̀ kan ni o kurò ni ọ̀gànjọ́. òru. Nkan burúkú ti sẹlẹ̀ si ọmọ rẹ̀ ọkùnrin ni o sáré bọ si ẹnu ọkọ̀ aladugbò wọn nigbàti o nfẹ̀yìn rìn ti o sì pá. Igbákejì rẹ̀ ni o sàlàyé fún wa, ohun ti o sẹlẹ̀, ti a o si sọ fún ẹnikẹni ti a fi ya fiimù nà tán. Sugbọ́n síbẹ̀ à sá ri pé à parí rẹ̀. Teepù mẹta ni a se ni ọjọ́ nà, a si kórawa jáde ni ori tẹlifisọ̀nu. Wow!

Nigbàti a bẹ̀rẹ̀ ètò gbigbóhùnjáde lori tẹlifisọ́nu, a kò ni òye bi ào tise máa san owọ́ fún ètò nà lọ́ ni kete ti a bá ti bẹ̀rẹ̀. Sugbọ́n Ọlọrun sì bẹ̀rẹ̀ si ni kọ́ wa pé kìíse owò $300,000 yìí nikan ni Ọ́n ó pèsè ti à nilo lati fi bẹ̀rẹ̀ ètò nàà, pé bakannà ni Ọ́n yóò tẹ̀síwájì lati máa pèsè owó nà fún yin lọ ni. Ọ̀pọ̀ nkan ni o wà ti a ni lati kọ́. Bi o tilẹ̀jẹ́pé àwa kò mọ̀ pé àwọn ènìyàn yóò dìde lati ràn isẹ́ ìránṣẹ orí àfẹ́fẹ́ wa lọ́wọ́; bi àti jẹ́ alaìmọkan tó nìyìí.

Mo sì ránti pé bí a ti bẹ̀rẹ̀ ètò ti àwọn ènìyàn ti ngbọ́ wa ni orí afẹ́fẹ́, ni Tracy, tí nse akọ̀we mi pè mi lati ilé iṣẹ wa, nigbàti mo gbe ìpè na, nise ni ohùn rẹ̀ ngbọ̀n. o ni "Pasítọ̀" ẹnikan tí ó nwo èto yìí fi sọ̀wedowó ẹ̀ẹ́dẹ́gbẹ̀ta pọùn. sọwọ́ sí wa. Àtipé pásítọ̀,nígbàti mo múu lati yẹ̀ẹ́ wò, ìfòróróyàn kanna ti o wa lorí owó igbà nì tí ẹ gbé bọ̀ lati ibi ètò ti ẹ se ni gbọ̀ngbàn ti Ìndia na ni ó wà ni ara rẹ̀ "Sé bẹ́ẹ̀ lorí" Mo sì nkólólò. Lóòtọ́ ni ẹnikan fi owó sọwọ́ sí wa?" "Kò tilẹ̀ wá si mi lọ́kàn pé àwọn ènìyàn leè ma fi owó ránṣẹ si wa lati ran ètò wa lọ́wọ́ à fi ìgbàti mo tó ri sọ̀wedowó náà gbà. Sùgbọ́n ẹyin Ọlọrun logo, àwọn ènìyàn ti nfi ètò nà rànṣẹ si ibi gbogbo ni àgbáye ojojúmọ . Owó naà titún ga si bi milliọnù ni ọdun kan, sùgbọ́n sibẹ̀ Ọlọrun si mú Ọ̀rọ̀ Rẹ̀ ṣẹ sí mi. Ọ́ nsan owó nàà ni igbàkúgbà.

Ìwe yìí ni se nipa gbígbọ́ àti bí Ẹ̀mi Mimọ́ Ọlọrun yóò ti se ma darí rẹ ninú ayé. Ìtàn ti àwa nsọ ni ori tẹlifisọ̀nu jẹ àpẹrẹ ti o dára nipa bi Ẹ̀mi Mimọ́ se ndarí àwọn ènìyàn lati se àwọn nkan nla ti wọn kò lérò pé o séese ninú àla wọn. Ohun gbogbo ti Ọlọrun se ninú ayé wa, jẹ́ nipa agbára wa ki íse lati mọ bi ìjọba Ọlọrun ti nsiṣẹ nikan, bikòsepé bakanà lati le gbọ́ àwọn ìtọ́ni ti Ọlọrun nfún wa, ọgbọ́n àti àwọn ìdahùn ti a nilò. Àwọn ìtànti mo sọ fún ọ yìí ko bá má sẹlẹ̀ bẹ́ẹ̀ tí ó bá se pé mi ò mọ̀ bi a ti ngbọ́ ohùn Ẹ̀mi Mimọ́ ni. Ní ọ̀pọ̀ ìgbà a le máa dojúkọ àwọn ìsòro ti o ga ti o le

máa ri bi pé kòsí ìrètí. Sugbọ́n Ọlọrun ni ìdáhùn si gbogbo rẹ̀.

"*Inu ẹnikẹ́ni ha bàjẹ́ nínú yín bí? Jẹ́ kí ó gbàdúrà"* (Jákọ́bù 5:13)

Kilóde ti wa fi gbàdúrà? Nitorí o nílò lati gbọ́ ìdàhùn, ìtọ́sọ́nà, àti ọ̀nà àbáyọ si wahálà nà. Bí èmi àti Drenda ti se rí ti wa nà ni ọ̀pọ̀lọpọ̀ ìgbà, Ọlọrun si tún le seé ju ohun ti a nrò lọ nigbà ti a ndojú kọ ìsòro. Yóò ràn ọ́ lọ̀wọ́ ni ọnà ti ó gbà yàtọ̀ àti nigbà miràn àwọn ọ̀nà àbáyọ́ àti ìlànà tí ó sàjejì to ó le mu o borí àwọn ohun ti o rò pé kò lé seése. Ọ̀pọ̀ igbà bi o ti se le gbọ́ ìdáhùn nà, ìyàtọ le wà láàrin bi o ti se le gbọ́ ìdáhùn si àseyọrí àti ti ìjakulẹ̀, ìyè àti ikú. Mo má sọ̀rọ̀ púpọ̀ nipa gbigbọ́ ohunti Ẹ̀mi Mimọ́ ninú ìwe yìí, sùgbọ́n sáàju jẹ́ kin se àpèjúwe bi Ẹ̀mi Mimọ̀ ti se le ràn ọ́ lọ́wọ́ ni ìgbà to ba le koko.

Nigbà ti à se ìfilọ́lẹ̀ iṣẹ àkànse ti ìkọ́lé ibi ti a wà bayìí, ti ìse milliọnu mẹfà àti àbọ̀ owó dọlla (6.5 million dollar). A ti sèkówójọ bi milliọnu mejì àti àbọ̀ (2.5 million) sílẹ̀ àti àwọn owó kan lati Bankì. A si tún ni àwọn owó kan ti o wọlé ni àrin ọdún kan àti àbọ ti a nse ikówójọ fún ètò ìkọ́lé. Iṣẹ àkànse nla ni fún ìjọ àwọn ènìyàn ti kò ju ọ̀tà-din-lẹ́wa dín ni ẹgbẹ̀ta lọ lati se. A fi ìpìlẹ̀ lé lẹ̀ ni ọdún 2007, ohun gbogbo si nlọ bóti yẹ titi di ọdún 2008. O le ránti ìyàn owó tómú ni ọdun 2008. a sì nba iṣẹ ile nà lọ láàrin gbogbo rẹ̀. Gbogbo nkan ni o wá ti gbówó lorí. ẹgbẹ̀rúnlọ̀dúnrún pọ́ùn ni ó tún ti lé si iye tí à ti lérò tẹ́lẹ̀. Àpẹẹrẹ kan nìyí. Gbogbo nkan ni o wá gbówó lorí ju ohun ti a ti setò pé a fẹ́ lò lọ owó gbogbo nkan ni o ti gbẹ́nu sókè ni ọdùn nà.

Bi ọdún na ti n lọ́ sópin, àwọn ile ìfowópamọ́, ni àsikò ti wa,àti pé nigbogbo orilẹ̀-èdè gbogbo ni wọn ti nfa àwọn onibárà wọn fún ẹ̀yáwó bi owó ti se wọn gógó tó. Àwọn onigbọwọ́ wá sọ́dọ̀ wa ni ọjọ́ kan lati sanwó eyíti wọn ti gbà lati fún wa. O ni lati san owó fun àwọn osìṣẹ́ àti san gbogbo gbese ti o wà nilẹ̀ ti àwọn owó ti a ti ná. Sọ̀wédowó milliọnu kan dọlla ni a fẹ́ lo ni ilé ifowópamọ́ nitorí à ti ná gbogbo owó ti o wà nilẹ̀ tán. Sọ̀wédowó na kò si nilẹ̀ mọ. Ìyàlẹ́nu ni o jẹ́ fún wà nigbàti a ri pé gbogbo ile ìfowópamọ́ ni wọn o gbà lati yá ẹnikẹni lowó mọ́. ki ise Bànki ti à wan lo nikan ni; sugbọ́n gbogbo Banki tí ó wà ni ilú ni. Àkọlé ti o wà

lori àwọn ìwe ìròyìn ni ọ̀sẹ̀ na ni pé, wọn ti da àwọn òsìṣẹ́ bi úúò duró lẹ́nu iṣẹ́ wọn sì ngbiyànju àti wa ọ̀nà àbáyọ́ si gbogbo wahála lori ìsúna tí ó ndojúdé lọ.

Bakannà, ohun tí ó wá sẹlẹ̀ ni pé àwọn òsiṣẹ nilò owó lati san fún àwọn agbanísíṣẹ ati lati san àwọn owó ohun èlò ìkọ́lé tí wọn ti lò. Sọ̀wédowó milliọnu kan dọlla yìí kì íse owó ti wọ́n fẹ́ lò ni ọjọ́ iwájú. Wọn tin á gbogbo owó nà tán! Nibáyìí àwọn ile iṣẹ́ àti àwọn ẹbi kan wà ti wọn fẹ́ kí à san owó fún àwọn abánisiṣẹ́ wa ki wọn ba le rowó san fún àwọn náà. Bi àwa nà ti se lerò pé àwọn Banki yóò sì tẹ̀ síwájú lati ma se ìrànwọ́ fún wa lọ ni àwọn onisẹ́ yìí na rò. Nibayìí? Kin ni nkan ti a le se ni irú àsikò bayìí? Èmi kò ni milliọnu kan dáni lọ́wọ́, mi ò sì setán lati lọ máa tọrọ owó lọ́wọ́ àwọn ọmọ ìjọ. Yàtọ̀ si èyí, Èto ti tẹlifisọ̀nu ti tún gbówó lorí bi a ti ngboro si lori àwọn nẹtiwọ́ki yókù gbogbo; ẹgbẹ̀rúnláàdọ́ta pọ́ùn ni a nsan ni ososù lorí afẹ́fẹ́. Kin ni ohun ti a le se ju nkan ti ìwe Jakọbu 5:13 sọ fún wa lati seé, gbàdúrà!

Ó wá sẹlẹ̀ pé àti tún ni ànfàni miràn lati lọ si Hawaii nipaṣẹ oko-òwò mi ni àsikò yìí gan nà. Mo wá ri pé àwọn Banki ti tún fi àyè yí silẹ̀ ni o ku bi ọjọ́ melo ti a fẹ́ kurò ni ilé. Bi mo ti nlọ si ibùdò ofurufú lati gbéra lọ si Maui, mo ni lati gbà pé àyà mi njà diẹdiẹ. Ọ̀pọ̀ nkan ni o kún inu ọkàn mi, ti ọkàn mi si nsáré mailli kàn ni ìsẹ́jú kan. Sugbọ́n bi mo ti nrìn nlọ ni ibùdòkọ̀ ofurufú, ti mo si nwo ara mi bayìí, Mo gbọ́ ohun Oluwa. Ó sọ pé " gbé ọpa rà sọkè" bi mo ti duró ti mo sì nronú lorí ohun ti Oluwa nsọ fún mi, lojijì mo ni òye ohun ti o sọ.

Ohun yìí kannà ni Ọlọrun sọ fún Mose nigbàti kò mọ ibití ó máa yà sí,bi àwọn ọmọ ogun Farao ti ká wọn mọ́ etí Òkun Pupa. Ọlọrun sọ fún Mose lati gbé ọ̀pá ọwọ́ rẹ̀ sorí omi, àti nigbati o se bẹ́ẹ̀, ó pin si mejì,o la ọ̀nà fún àwọn ọmọ Ìsraẹli lati kọjá àti gbà wọn. Ọ̀pa Mose dúró fún ìlérí ti Ọlọrun sọ fún un, bakana bi àṣẹ ti o fi fún wọn lat se iṣẹ nà.

Mo mọ ohun ti Ọlọrun nsọ fún mi ni àkòkò nà.Èmi si ni adarí, Pasitọ ìjọ yìí; a ti fún mi ni àṣẹ lati ba gbogbo ipòkípò wí. Mo ni lati mú àsẹ mi àti ki sì dúró ki nsi wá ọ̀nà àbáyọ. Nigbàti a dé Hawaii, ohungbogbo ti mo le se na ni kin gbadúrà. Mi o le sùn ni òrú ọjọ́ nà.r Ẹ̀mi mi njà gbùdù ninú mí, mo si mọ́ pé ìjàkadì nlọ ninú ẹ̀mi mi fún ìdáhun tí mo ní lò. Lakótán,

Drenda ni àwọn èro kan ti o gbàgbọ́ pé lati ọ̀dọ̀ Oluwa ni o ti wá. Ọpẹ́ ni fún Ọlọrun fún ìyàwó mi! ọ̀pọ̀ igbà ni Ọlọrun ti lòó lati wa ọ̀nà ati ìtọ́ni ni ìru àwọn àkókò báyìí. Mi o lé sàlàyé bi o ti niyì àti seyebíye tó ni ojú mi àti bi mo ti se fẹ́ràn rẹ̀ tó. Nkan kìí sú u!

Èrò rẹ̀ rọrùn sibẹ̀, ó niye lorí gan. Kò si ohun ti o fi hàn pé yóò siṣẹ tàbi seése, sùgbọ́n à bẹ̀rẹ̀ iṣẹ lorí rẹ̀ ni kiákiá. Ohun ti a rò ni wípé a o fi ohun gbogbo ti a fẹ́ lati se lọ sí banki àwọn abánisiṣẹ́ wa , ki ise banki ti wa, a o wá bèrè fún ẹ̀yáwó. Àwọn ohun ti a ba kó kalẹ̀ yóò sàfihàn rẹ̀ fún banki irú ẹni ti àwa jẹ́ àti ìdí à fi lerò pé ẹ̀yáwó nà lẹ́tọ́ ki wọn fún wa. Nkan nla ni , nitori bi mo ti se nsọ, gbogbo banki ni ni ilú ni wọn kò yá ẹnikẹ́ni ni owó mọ. Èrò wa si ni pé tí à kò bá sanwó fun àwọn oniṣẹ wa, ọ le di gbèsè sí wọn lọrùn, nigbàti o ba kó gbogbo owó ti o sẹ̀ṣẹ̀ yá àti àwọn èyítí o ti yá tẹ́lẹ̀ papọ̀ ni banki rẹ̀ le mú ki o ma ri san, o sì le jẹ́ ewu nla fún banki nà, nkan ti a sì mọ pé wọn o ni fẹ́. Ati pé,èyí kìí se banki ti wa, wọn kò si ni àsepọ̀ tàbi ni ìtàn kankan ti o ni se pẹlú wa.

A wá se ìwe kan ti a se àpèjúwe ara wa si iyè àwọn ti ongbé ni àgbègbè wà, ọjọ́ orí wọn àti bi àdugbò na ti se ndagbà sí. A fi ìtàn ara wa hàn ni bankì àti bi ati se ngbèrò ati tètè dàgbàsokè si. A tún wa àwọn ọ̀nà miràn ti o le mú kí ilé naà ma mú owó wọlé yàtọ̀ si isìn wa ninu ìjọ, gẹ́gẹ́ bi tẹlifisọ̀nu ti nmú ọwó wọlé si àti ọ̀pọ̀ àwọn nkan miràn ti o le jẹ́ èrè fun wọn. A fẹ́ mu dáwọn lojú pé ewu nla ni a jẹ́ ti yóò mú èrè nla wá fún banki nà, kódà ni àsikò tí o le kòkò yìí. A tún fẹ̀ ki o yé wọn wípé ti àwọn osiṣẹ na kò bá rí owó gbà, wọn le wà ninú ewu sísọ nkan nla nù ti àwa si fẹ́ " lati ràn wọ́n lọ́wọ́" lati yàgò fún. Wọn ni ki a lọ lati rí igbákejì Àárẹ banki nà ti o jẹ́ àsojú fún ẹ̀ka ayánilowó. A gbàdúrà a wá lọ si ofisì nà pẹlú ìgboyà nitorí à mọ̀ pé ètò ti Ẹ̀mi Mimọ́ fi fún wa ni, o si ti bẹ̀bẹ̀ fún wa.

Sí ìyàlẹ́nu, lẹ́yìn igbàti à sàfihàn ohun gbogbo tán, ọ̀ga nà sọ fún àkọ̀wé rẹ̀ lati já sọ̀wédowó ẹ̀ẹ́dẹ́gbẹ̀ta pọ́ùn fún ìjọ lati ma gbà lọ, oni ohun ti oun nse ki ise ojú lásán ki siì se bi a ti máá se niyìí. Kò si àkọsilẹ̀ ti à kọ, kò sí fọọmù, sọ̀wédowó fún ẹ̀ẹ́dẹ́gbẹ̀ta pọ̀ùn nikan ni. Ó wá sọ pé ẹ̀ẹ́dẹ́gbẹ̀ta

**TI O BÁ JẸ́ PÉ O MÁA FỌWỌ́BÀ NINÚ AGBÁRA ÌFIYÈSÍ TI ÌJỌBA ỌLỌRUN, O MÁA NILÒ LATI KỌ́ BI O TI SE LE MÁA GBỌ́ OHÙN TI Ẹ̀MI MIMỌ́.**

pọ̀ùn tókù à ní lati kọ̀wé àdéhùn silẹ̀ lorí rẹ̀,o si fid á wa lójú pé yóò gbàá wọlé nitorípé oun nà ni o sọ bẹ́ẹ̀, ti o si seé. A sì san milliọ̀nù kan dọlla fun àwọn osìsẹ́ abanikọ́lé nà wọn si parí iṣẹ́ ile nà.

Ó sòro diẹ fún wa lati sọ bi inú èmi àti Drenda ti se dùn tó nigbà ti a npadà lọ si ilé pẹ̀lú ìwé sọ̀wédowó ẹ̀ẹ́dẹ́gbẹ̀ta pọ̀ùn ni àpò wa. Ìnu wá dùn gan ni a si rí ara wa bi ènìyàn nlá! Kòsí gbólóhùn ọ̀rọ̀ ti a le fi sàpèjúwe bi a ti wà ni àkókò nà, sùgbọ́n ẹ̀rù Ọlọrun bà wá fún ohun ti Ẹ̀mi Mimọ́ se fún wa. Ẹni àkọ́kọ́ ti a pè ni àwọn ti o nbá wa siṣẹ́. Mo si tún gbọ́ ohùn rẹ̀ bi ayọ̀ ti hàn to ninú rẹ̀ nigbàti ó gbọ́ iròyìn ayọ̀ nà, O se kinni?" ni ohun ti ó kọ́sọ.” Wọn fún ọ ni sọ̀wédowò lojú ẹṣẹ̀ nibẹ̀ nà?" Àwa mejejì sì mọ̀ pé Ọlọrun ni.

Bawo ni ó ti se sẹlẹ̀? Ẹ̀mi Mimọ́ ni! Ọlọrun ni àwọn ìdáhùn sí ohun ti ó nilò, ọrẹ́. Tí o bá jẹ́ pé o máa fọwọ́bà ninú agbára ìfiyèsí ti ìjọba ti Ọlọrun, o má nilò lati kọ́ bí o ti se le máa gbọ́ ohùn ti Ẹ̀mi Mimọ́. Gbogbo nkan ti ìwé yìí nsọ nìyìí.

Rínrìn pẹ̀lú Ẹ̀mi Mimọ́ ninú ipòkípò jẹ́ nkan tó wúnilorí jọjọ ju ki a máa wo fiimù James Bond ti o ti wò rí! Gẹ́gẹ́ bi fiimù, wa ti mọ ẹni ti yóò borí lopín eré, kó sí bi àkókò na ti se le tó.

ORÍ KEJÌ

# ÌJỌBA NÁÀ

Mo mọ dájú pé ọ̀pọ̀ wa ni a ti n gbọ̀ nipa àwọn ẹ̀sùn ti kò lẹ́ṣẹ̀ nlẹ̀ ti wọn ngbé lọ silé ẹjọ́ ti ilé sì da àwọn ẹjọ́ nà nù. Àpẹẹrẹ ni yìí.

Ọkan ninú àwọn ẹlẹ́wọ̀n ni ọgbà ẹ̀wọ́n Colorado ti ó lọ lati fi ẹ̀sùn kan àwọn ẹgbẹ́ à gbá Bọọlù (National Football League) ni owó ti o lé ni $88 billiọnu (b*ẹ́ẹ̀ni*, b*íllíọ́nù*). Ẹ̀sún na wáyé lati ipaṣẹ òfin ti awọn òsìsẹ́ agbá bọ́ọ́lù nàà se nigbàti eré ìdije wáyé láàrin Dallas Cowboys àti àwọn Green Bay Packers. Àwọn òsìṣẹ́ na sọ wipé bọ́ọ́lú ti Dez Bryant ti íse ọmọ ẹ́gbẹ́ (Cowboys) gbá wọlé kò bófin mu. Ọ̀kan lára àwọn ẹlẹwọ̀n na wá takòó. Ẹsùn ti o wa fi kan àwọn òsìsẹ́ NFL náà nipé wọn hùwà àìbìkítà àti yẹ àdéhùn ìgbẹ́kẹ̀lé ti ojuse wọn. Kilode ti ẹlẹ́wọn yìí fi pè wọn léjọ́ $88 billiọnu? Nitorípé nọmba ti o wà lára àsọ ti Ọ̀gbẹ́ni Bryant fi ngbá bọ́ọ́lù ni 88.[1]

Sé ìwa wèrè kọ́ niyìí, O dáa? Mo rò wipe gbogbo wa ni ó mọ̀ pè ẹjọ́ nà kò lẹ́ṣẹ̀nlẹ̀. Sugbọ́n nkan ti ó máa nsọ bóyá ẹjọ́ fẹṣẹ̀múlẹ̀ tàbi kò fẹṣẹ̀múlẹ̀? O dáa, gẹ́gẹ́ bi òfin ti sọ, àwọn ìdí pàtàkì mejì ti wọn fi máa n da ẹjọ́ nù nilé ẹjọ na ni pé bóya ẹjọ nà ní agbára ọ̀rọ̀ ti o fẹ́sẹ̀ mulẹ̀ tabi kò ni ẹṣẹ̀ mulẹ̀ labẹ́ ófin bi òfin ti làá kalẹ̀. Kílóde ti mo fi nsọ̀rọ̀ nípa òfin ninú ìwe ti Ẹ̀mi Mimọ̀? Nitori ti o bá fẹ́ ri ki Ẹ̀mi Mimọ̀ rin tàbi dásí ipo to wà, o ni lati mọ ohun ti ofin sọ dáadáa. Ìjọba ti Ọlọrun, jẹ́ ìjọba, ti o nsìṣẹ́ láàrin àálà òfin ti ìjọba Ọlọrun. Ninu àwọn ìwe mi mejejì to se yebíye ti ó tẹ̀léra yìí, *Yíyí ẹ̀tò ìsúná rẹ padà: Agbára ìfọkànsìn àti Yíyí ètò ìsúná rẹ padà Agbára Ìsinmi,* Mo kọ àwọn kókó ti ó se pàtàkì bí Ìjọba Ọlọrun ti nṣìṣẹ́ nipa ti ẹ̀tọ́ àti agbára lati lòó ati lílo òfin. Sugbọ́n fún ọ lati mọ ohun ti mọ nsọ ni ti Ẹ̀mi Mimọ̀, ó le sewá ni anfàni lati leè ma rán ara wa létí

àwọn òfin wọ́nyìí. Ẹ jẹ́ ki a bẹ̀rẹ̀ pẹ̀lú ìdánwò kékeré.

> *Jesu wí fún wọn pé, "Kò sí woli tí ó wà laílí ọlá," **<u>Òn kò sí le se</u>** <u>isẹ́</u> agbára kan níbẹ̀, ju pe o gbe ọwọ́ rẹ̀ lé àwọn aláìsàn diẹ, ó sì mú wọn láradá. Ẹnu sì yà a nitorí àìgbàgbọ́ wọn.*
>
> —Maaku 6:4-6

Se o le sọ ìdí ti Jesu kò fi le wo àwọn ènìyàn sàn ninú ẹ̀sẹ tí a kà yí? Ìdáhùn ti o yẹ kí o jẹ́ nipé, boyá ifẹ́ Ọlọrun ni lati má wò wọn san. Niwọ̀n igbà tí Ọlọrun mọ èyí tó dára jùlọ, ti ó ba fẹ́ kí wọn ri ìwòsàn, kò bá ti sé, ohun ti mọ nsọ ni pé Ọlọrun ni. Se ìwọ na yóò rò pé àwọn ènìyàn kan nà wà nibẹ̀ ti wọn nilò ìwosan, sùgbọ́n ti wọn o gba ìwòsàn wọn? Mo lerò pé o hàn kedere ninú ọ̀rọ̀ ná.  Lati mọ́ ìdahùn idi ti Jesu kò fi le wò àwọn ènìyàn náà sàn jẹ́ ìbérè tó se pàtàkì, ti  a gbọ́dọ̀ dáhùn. Tí a bá ka ìtàn na parí, ao ri ti Jesu sọ pé nitorí àìgbàgbọ́ wọ́n ni o sokùnfa ti o di wọn lọ́wọ́ àti rígbà. Tí le ni oye ohun ti Jesu sàkiyèsi àti ìpinnu rẹ̀ ti kò jẹ̀ ki àwọn ènìyàn yìí gbàá, a ni lati ní ìwòye ti o dára ohun ti ìgbàgbọ́ jẹ́ àti ìdí ti o fi nilò ni ìpele ti ayé yìí fún ọ̀run lati le gba agbára lábẹ́ òfin nibiyìí.

Ẹ jẹ́ki nsọ àkópọ̀ ọ̀rọ̀ yìí nisókí. Kì íseti àini agbára ati fojú ìwoyé wòó bi ti Jesu. Ohun ti o wà nibẹ̀ nà ni ọ̀rọ̀ ti sàkání agbára.  Pàtàkì julọ́, ọ̀run gan kò ni òfin ti o gbé kalẹ̀ lati le gba ipò na ti ọ̀pọ̀ àwọn ènìyàn wà. Bayìí kí o to sọ ìwe ọwọ́ rẹ́ yìí nu si ẹgbẹ́ kàn pé nkan ti o nsọ yìí kò yé mi, ya mi ni bi ìsẹ́jú diẹ kin fi se àlàyé.

Nigbàti Adamu àti Efa wa lorí ilẹ̀ ayé wọn ni gbogbo agbára àti àṣẹ lórí ilè ayé. Mo lerò pé ẹṣẹ ti a fẹ́ kà yìí fi idì ọ̀rọ̀ mi mulẹ̀ kedere.

> ***Ì**wọ dáa rẹlẹ̀ diẹ̀ ju àwọn ángẹ́lì lọ; ìwọ fi ògo àti ọlá dé e ní adé, ìwọ sì fi I jẹ olórí isẹ́ owó rẹ: Ìwọ fi ohun gbogbo sábẹ́ ẹsẹ̀ rẹ̀. Nítorí níti pé o fi ohun <u>gbogbo sábẹ́ rẹ̀ ko ku ohun kan ti kò fi sábẹ́ rẹ̀</u>*
>
> —Heberu 2:7-8

Sàkíyesi pé Bibeli ni à fi ògo àti ọlá dé Adamu ni adé. Ade nibiyìí ni o ntọkasi àṣẹ ti Adamu fi jọba, ki ise pé a gbé ade lée lorí ninú ọgbá. Sugbọ́n

à le wòó pé o le máa tàn yiká, èrò ni. Adamu ni ògo (ìfòróróyàn ati ọlánla ti ìjọba náà) ati ọlá (ipò àṣẹ)ti ìjọba Ọlọrun. Láarin àwọn nkan meji yìí, ó njọba lorì ilè ayé, pẹ̀lu àṣẹ ti a fi fún, nitori ti ìjọba Ọlọrun. Satani, ti o wà lorí ilẹ̀ ayé, ki a tó sẹ̀dá ènìyàn, ó kẹ́gàn ènìyàn àti mú u ki ó le lo àṣẹ nà ni o ninu ìfẹ́kúfẹ̀. Ó mọ̀ pé oun kò le gbà adé àṣẹ lọ́wọ́ Adamu pẹ̀lu ìrọ́rùn, bi Adamu ti se ní àṣẹ lorì rẹ̀, o wá ni lati lo ọgbọ́n àrékérekè fún un ki o ba le mu ki o fi gbé adé (àṣẹ) náà kalẹ̀ fúnrarẹ̀.

Satani lọ tan Efà, Adamu nà si tẹ̀le, wọn ditẹ̀ si Ọlọrun, èsì àbáj áde nà ni pé wọn sọ ipò wọn nù ninú ìjọba ti Ọlọrun. Wọn tẹ̀lé Satani ni bayìí wọn ti wà ni sakáni ti ìjọba rẹ̀. O wa le bèrè pé, "Kilodé ti Ọlọrun fi fàyé gba Satani ninú ọgbà lákọ́kọ́?" Ó dáa, Ó yẹ kó se bẹ́. Mo mọ̀ pé ìdahùn mi yìí le yà ọ lẹ́nu, sugbọ́n wàá ri pé otitọ́ ni. Ẹ jẹ́ ki a lọ wo ìwe Gẹnẹsisi 2:8-9.

> *Oluwa Ọlọrun sì gbin ọgbà kan nihà ìlà-orùn ní Edẹ́nì; níbẹ̀ ni ó sì fi ọkùnrin na tí o ti mọ sí. Oluwa Ọlọrun mú oniruru igi hù jáde wá ti o dára ní wíwò, tí ò sì dára fún óunjẹ; igi ìyè pẹ̀lú larin ọgbà na, àti igi ìmọ̀ rere àti búburú.*

Bi a ti se nka ẹ̀kọ́ yi o le máa yà wá lẹ́nu pé kin ni se ti Ọlọrun fi fi igi Ìmọ̀ Rere àti Buburú si àrin Ọgbà ti o kan Igi Ìyè. Ni Pataki lati sọ́ di ẹ́tọ́ labẹ́ òfin fún Ọlọrun lati le gbogun ti agbègbè ti Satani. Ọlọrun kò ni le kùn wá sí agbègbè Satani ki o wá fi èniyan sibẹ̀ laisi òfin. Kó ba le dòfin, ènìyàn gbọ̀dọ̀ le yan ẹni tí o fẹ́ lati má tẹríba fún. Niwọ̀n ìgbà ti èniyàn bá ti yan Ọlọrun, Igi Ìye, èniyàn ni yóò máa jọba lórí Satani. Bayìí Igi Ìmọ̀ Rere àti Buburú ni lati wà ni ẹ̀gbẹ́kẹ̀gbẹ́ Igi Iyè.

Ohun pàtàkì kan niyìí ti a nilo lati kíyèsì làti se.A kò le dá ènìyàn sórí ilẹ̀ áyé laini agbára àti yàn/ se ìpinnu. Mo mọ àwọn kristiani kan ti wọn ma nsọpé a dáwa pẹ̀lú lakáyè ni ki Ọlọrun fúnrarẹ̀ le da ẹni ti o fẹ́ràn Òun mọ̀. Mo le sọ pé òtítọ́ wà ninú ọ̀rọ̀ nà.Sugbọ́n ni pàtàkì jùlọ, kò bá lòdì labẹ́ òfin ti kò bá si agbára lati yàn. Ti o bá jẹ́ wipé a kò fún ènìyàn ni laakáyè ni, kò bá má le wa nibití à fi sí. Ọpọ̀lọpọ̀ ni o tun kùti mi o ba bá yin jiroro, sugbọn ti mo ti sọọ ninú àwọn ìwe mejì ti mo ti se sáàju.

Torinà Adamu gbà ẹ̀tàn ti Satani, o si pádanù ìjọba ti Ọlọrun, Ọlọrun si kòó èniyàn lojúkorojú. Gẹnẹsisi 3:17-19.

> *A fi ilẹ̀ bú nítorí rẹ; ni ìpọ́njú ni ìwọ o ma jẹ nínú rẹ̀ ni ọjọ́ ayé rẹ gbogbo; Ẹgún on òsùsù ni yóò ma hù jáde fún o, ìwọ o sì ma jẹ ewéko ìgbẹ́. Ni òógùn oju rẹ ni ìwọ o maa jẹun, titi ìwọ o fi padà di èrùpẹ̀*

Ní pàtàkì jùlọ́, Ọlọrun sọ fún Adamu, pé ìwọ Adamu, o ti fi ilẹ̀ bú. Nitoripe Adamu ni ominira pátá lórí ilẹ̀ ayé, Oun ni ẹni tí o silẹ̀kùn silẹ̀ fún Satani lati wa máa jọba àti ti Ọlọrun sóde. Ọwọ́ Ọlọrun ti wa kún bayìí, Adamu yóò wa máa jẹ ninú ìpọ́njú àti ninú òógún ara rẹ. Ohun kekeré kan wà ti Satani gbàgbé lati sọ fún Efa nigbati ó ndánwò lọwọ́. Náà ni pé Ọlọrun ti da Satani lẹ́jọ́ na, o si ti lè jáde kúrò ni ọ̀run, o si ti kéde pé ile ayérayé rẹ̀ ni a o ma pé ni ọ̀run àpáádì. Óse patàkì ki o ni òye nkan wọnyìí. Ọ̀pọ̀ èniyan ni o nwipé" Bawo ni Ọlọrun onífẹ̀ ti se le lé àwọn èniyàn jù sí ibi tí à npè ni ọ̀run apáadi?" Kò rí bẹ́ẹ̀, Adamu ni o seé. Bi a ti se ri ninú ẹṣẹ ti a kà, pé a kò dá ọ̀run apáàdi fún èniyàn.

"Nígbànà ni yóò wí fún àwọn tí ọwọ́ òsì pé, 'Ẹ lọ lọ́dọ̀ mi, ẹ̀yin ẹni ègun, sinu ìna àinipẹ̀kun, tí a ti pèsè sílẹ̀ fún Esù àti fún àwọn Angẹli rẹ. Nígbàna ni yóò wí fún àwọn tí ọwọ́ òsì pé, Ẹ lọ lọ́dọ̀ mi, ẹ̀yin ẹni ègún, sínú iná aìnípẹ̀kun, ti a ti **pèsè sílẹ̀ fún Èsù àti fún àwọn ángeli rẹ̀**'" (Máttiù 25:41)

Nigbàti Adamu àti Efa ti wá wà labẹ̀ ìdarí ti Satani, wọn tún ti wà lábẹ̀ ìdajọ Satani. Gbogbo ìrìn-àjò gbogbo ènìyàn wá sábẹ̀ ìjọba Satani nipaṣẹ Adamu. Ròó pé o fẹ́ se ọ̀sin maalu. Ti ọkan ninú àwọn maalu rẹ bá bimọ̀, wàá ko mọ èyí tì o ti ni nitori ìwọ na ni o ni gbogbo rẹ̀. Ti o wá jẹ́ wipé gbogbo àwọn ọmọ Adamu ti wà ni sàkáni ti Satani. Jẹ̀ ki nsọ pé àìnìmọ́, nipé kádàrá/ àyànmọ̀ ẹnikan, bóyá ni ọ̀run ni tàbi ni ọ̀rún àpáádì ni, ó wà lórí bi o ti dára si tàbi ya ẹni ibi si, àsise patá gbáà ni. Ohun ti o dajú nibẹ̀ nipé a ti dáa lẹ́jọ́ tẹ́lẹ̀. Ọ̀run àpáádi ni gbogbo wọn nlọ. Ki íse pé

won se àsìse kàn rárá, sugbọ́n nitorí ohun ti Adamu ti se. Nibayìí Nitori ìfẹ́ ti Ọlọrun ni fún ọkùnrin àti obinrinti o dá, Ó ti setò àti gbà wá nipaṣẹ Jesu Kristi ti o mú ọkùnrin àti obìnrin bọ́ lọ́wọ́ ìdajọ́ ti o wá mú wa padà wá sinu àgbára ti ìjọbà Ọlọrun.

*Ẹniti o **gbà** wá lọ́wọ́ agbára òkùnkùn tí ó si si wa nipò sínú ìjọba àyànfẹ́ ọmọ rẹ̀. (Kólósè 1:13)*

A gbọdọ̀ mọ̀ pé labẹ́ òfin Ọlọrun ti yọ wa kúro ninú ẹjọ́ ati ìdajọ ti Satani. Bikose lati mú ànfàni nà lo, lọkúnrin lobinrin, lọ́mọde, lagbà gbọdọ́ mu ànfani yìí lò nipa pípe orukọ Jesu. Ìwọ kristianni, jọ̀wọ̀ tẹ́tísilẹ̀ si mi ni àkókò. Ọmọbinrin ti o rẹwà jùlọ ni àdúgbò rẹ yóò ba ara rẹ̀ ni ọ̀run àpáádi àyàfi ti ẹnikan bá s; fún lati pé orukọ Jesu ki o tó di pé ó kú. Ọ̀pọ̀lọpọ̀ àwọn ènìyàn tódára ni yóò pọ̀ ni ọ̀run àpáádì. Irọ́ Satani ni ó máa mu ki àwọn èniyàn lerò pe àwọn le sá àsálà kúrò ni ọ̀run àpáádì nitorí iṣẹ rere ti wọ́n nse. Orúkọ Jesu nikan ni orukọ ti a fí fún gbogbo ènìyàn lọkùnrin ati lobinrinlati di ẹni ìgbàlà àti sá àsálà kuró ninú ìdajọ̀ Satani. Mo tún fẹ́ kí ó yé wa pé nigbàti Adamu subú, ọkú ikú t'ẹ̀mí àsì ge kúrò ni ọ̀dọ̀ Ọlọrun; bakanna, ó si tún nsetọ́jú <u>ìṣẹ rẹ̀</u> fún ra rẹ̀ lorí ilẹ̀ ayé. Nigbàti o wá ri báyìí, Satani wa nílo lati lo àwọn ẹ̀mi okùnkùn rẹ̀ mú ìwúrí ba àwọn èniyàn, Ọlọrun wá lati lo àwọn èniyàn ti ò kún fún Ẹ̀mi Mimọ́ lati se ohun gbogbo ninú ìjọba ti èniyàn. Ninú àtúnyẹ̀wò a rí wipé ni lílọ si ọ̀run tàbi ọ̀run àpáádì jẹ́ ọ̀rọ̀ òfin ni kò si dúrò lorí bí o ti dára si, sugbọ́n ó dúró lórí ìsẹ́gun ti Jesu sẹ́gun Satani lori igi àgbélébu. Bíótìlẹ̀jẹ́pé Jesu sọ ọ́ di òfin fún gbogbo èniyàn lati jáde kurò ni sàkáni Satani, àti bakannà gbogbo ènyàn ni ó gbọdọ̀ pé orukọ Jesu ni ìgbàgbọ́ lati se bótiyẹ.

Mo mọ̀ pé àti njiròrò bọ̀ lorí ọ̀rọ̀ yìí tẹlẹ̀, bayí ẹ jẹ́ kí a tún lọ gbée àwọn ìbèrè ti a ti bèrè tẹ́lẹ̀ yẹ̀wò, "Kilóde ti Jesu kò se le wo àwọn èniyàn na sàn ninú Máàkù 6?" Mo sọ pé ọ̀rọ̀ sàkáni agbára ni, bẹ́ẹ̀ sì ni, Niwọ̀n ìgbà ti Adamu ti gbé sàkaní agbára t'ẹ̀mi ti ìjọba ènìyàn lée Satani lọ́wọ́, Ọlọrun kò kan le wá sibẹ̀ nigbàti ó ba fẹ́ nitori ó ni lati jẹ́ labẹ́ ófin. Nisisiyìí, má jẹ́ kí ohun ti mo sọ rú ọ lójú pé ni ẹniti o ni ayé tìkararẹ̀.

Bibeli sọ pé Ọlọrun ni o ni ilẹ̀ àti ẹ̀kún rẹ̀. Sibẹ̀síbẹ̀, ni ti ìjọba ènìyàn, Ọlọrun kò ni àṣẹ lorú wọn. A le rí kà ninú Ìwe Luku 4:5-7

*Èsù sì mu u re orí òkè gíga, o sì fi gbogbo ilẹ̀ ọba aye hàn án ni ìsẹ̀jú kan. Èsù sì wí fún pé, Ìwọ ni èmi o fi gbogbo agbára yìí ati ògo wọn fún; gbogbo rẹ̀ ni a ti fifún mi, ẹnikẹ́ni tí ó bá sì wù mi ni èmi á fi fún. Njẹ́ bí ìwọ bá foríbalẹ̀ fún mi. Gbogbo rẹ̀ ni yóò jẹ́ tìrẹ*

A le ri nibiyìí pé Adamu ti fi gbogbo agbára ti ìjọba ènìyàn ni ayé le Satani lọ́wọ̀. Nitori ìdí èyìí, Ọlọrun kò kan le wa se ohun ti o bá fẹ́ lorí ilẹ̀ ayé ti o ni se pẹ̀lú àwọn èniyàn. Sugbọn tí Ọlọrun bá le rí ọkùnrin tàbi obinrin tí ó gbàágbọ́. ti o si ti ni ìyìpadà ọkàn nipa àṣẹ t'ọ̀run, nígbànà Ọlọrun yóò lo agbára àṣẹ rẹ̀ nipaṣẹ iru èniyàn bẹ́ẹ̀. Ọ̀na yìí kannà ni Satani gbà lati wọlé si ìjọba ti ayé ni àtètèkọ́se, nipaṣẹ ẹni ti ó ni òfin lorí iṣẹ́ lorilẹ̀ ayé, tin se Adamu. Nigbàti Ọlọrun padánu ènìyàn Rẹ̀ Adamu, Ó ni lati wá onà miràn padà sí orílẹ̀ ayé lati fi èròngba gbígbà wa silẹ̀ sípò, orukọ̀ arákùnrin na ni Abrahamu.

*Oluwa sì ti wí fún Abramù pé, jáde kúrò ni ilẹ re. àti lọ́dọ̀ àwọn ara rẹ, àti kúrò ní ilè baba rẹ sí ilẹ kan tí èmi o fi hàn ọ́. Emi ó sọ ọ́ di orílẹ̀-èdè ńla, èmi o si bùsi I fún ọ, èmi o sì sọ orukọ rẹ di ńla, ìbùkún ni ìwọ ó si jásí. Èmi o sì bùkún fún àwọn tí ńsúre fún ọ, ẹnití o nfi ọ́ ré ni emi o fi re: nínú rẹ ni a o ti <u>bùkuń fún gbogbo ìdíle ayé.</u>*

—Gẹ́nẹ́sisi 12:1-3

Abram tàbi Abrahamu, ni ìlẹ̀kùn ti Ọlọrun lò lati pada wọlé si orilẹ̀ ayé àti tún mú èròngbà Rẹ̀ lati mu ìgbàlà wá fún ìran ọmọ èniyàn. Ọlọrun sì ba Abrahamu dá Majẹ̀mu òun àti àwọn ìran rẹ̀, nipaṣẹ adéhùn lábẹ́ òfin, Ọlọrun wá ri ààyè lati mú Jesu Kristi wá sinú ayè, sugbọn lati ipaṣẹ ìran Abrahamu. Ìdí sìnìyìí ti Jesu fi wá lati inú ìran Abrahamu ti wọn kò fi ayè gba àwọn ọmọ Israẹli lati máa segbéyàwò lààrin àwọn ti ó múlé tì wọ́

n. Ohun nà ni o fàá ti ìwé àkọ́kọ́ ti Majẹ̀mú Titun fi jẹ́ ọ̀rọ̀ lorí àwọn ìdílé. Ó fi hàn pé Jesu ni, ni òtítọ́, ìran Abrahamu ni lábẹ́ òfin, ó jẹ́ ẹri fún Satani pé ẹ̀tọ́ ni fún Jesu labẹ́ òfin lati wa àti san ìdíyelé fún ẹ̀ṣẹ̀.

Niwọn ìgbà ti ọkùnrin àti obinrín sì ni ẹ̀tọ́ ìsàkóso lorílẹ̀ àyé, kòsí ohun tó tún rújú mọ́ ninú ìsàkósó t'ẹ̀mi, Ọlọrun àti Satani yóò lo àwọn èniyàn lati ri pé wọn seé. Ni èdè kúkúrú, ọkùnrin àti obinrin ni o jẹ́ nkankan labẹ́ òfin lorílẹ̀ ayé. Gẹ́gẹ́ bi Satani ti rí àyè wọlé nipaṣẹ Adamu, ti Efa nà si gba ohun ti ó sọ gbọ́, bẹ́ẹ̀ náà ni Ọlọrungbọdọ wá èniyàn ti yóò gbà ohun ti ó bá sọ gbọ́ lati leè ri ayè ní orílẹ̀ ayé bakannà. Tí ọkùnrin tàbi obínrinna bà ti gbàgbọ́ pátápátá ninu ọkan rẹ̀ohun ti ọ̀run nsọ yàtọ̀ si ohun ti Satani nsọ ninú ìjọba rẹ̀, ni a npé ni ìgbàgbọ́, ó si nfún ni ní agbára labẹ́ òfin si sàkáni ti ọ̀run lati le lọ pẹ̀lú ìru ẹni bẹ́ẹ̀ wa sinú ayé àti mú ki ìfẹ́ Ọlọrun jẹ́ri tako ìjọba ti Satani. Ọ̀pọ̀ nkan ni o wà lati sọ, sugbọ́n mo ti sọ àlayé púpọ̀ lorí rẹ̀ ninú ìwe mi meji ti ọ sáàju.

Kọ́kọ́rọ́ rẹ̀ gan nìyìí. Niwọn ìgbà ti Satani si wà ninú ayé, gbogbo ìgbà ni ó máa dáabòbo ìjọba rẹ àti tun máa gbiyànjú lati lé ètò ti Ọlọrun bá. Nitorí èyí, Ọlọrun nsiṣẹ labẹ́nú lati le mú èrò àti àwọn ète-ìlànà rẹ̀ wá sinú ayé. Ati ninù mí mọ bi Ọlọrun ti nsiṣẹ labẹ́nú ni o ti le rí kọ́kọ́rọ́ seyori nla àti ti ìṣẹ́gun ninú ayé rẹ. Mo sì pé ni agbára ilànà!

ORÍ KẸTA

# OHUN ÌYÀLẸ́NU

Ẹnìkan pè mi lorí ẹ̀rọ ìbanisọ̀rọ̀ mi o ti bá ẹni ma pàdé ri. Ó juwe ara rẹ̀ fún mi óni òun ati àwọn ọ̀rẹ́ on kan ngbàdun ìwé ti mo kọ kan ti o danilẹ́kọ́ nipa ìjọba Ọlọrun ti mo pè ni *Sísọdẹ ìgbàgbọ́*. Kódà, lótítọ́, ó bi mí lérè pé, sé mo le wá sí Montana lati wad á àwọn ènìyàn bi ààdọ́rin lẹ́kọ ni alẹ́ ọjọ́ Jimọ̀ àti ni òwúrọ̀ ọjọ́ Sátidé.Kín tó dáalohùn, ó ti ni, Lẹ́yìn ìdanilẹ́kọ́ na, ní òwúrọ̀ ọjọ́ Satide, àwọn o fẹ́ lati gbé mi jade lati lọ sọdẹ̀ ẹtu nitori àkókó wọn la wà. kò pẹ́ tí mo fi dá wọn lóhùn rárá. Ó ni àwọn arakùnrin mi náà le tẹ̀lé wa bi wọn bá fẹ́. Ni asìkò ìgbà ooru ti ó mbọ̀, wọn o ranmilọ́wọ́ lat gba ìwé àṣẹ tó yẹ fún ìsọdẹ ti ó tun mbọ́. Ọmọ mi Tim nà ti gbá lati tẹ̀lémi pẹ̀lú, àti gba ìwé àṣẹ tirẹ̀ nà .

Bí mo ti rí, àwọn ẹgbẹ́ ti wọn máa pa ìlérí wọn mọ́ ni, Wọn sì nifẹ́ si ìtàn sísọdẹ ti mo sọ ninú ìdanilẹ́kọ mi àti bi mo ti se gba àgbọ̀nrín mi nipa ìgbàgbọ̀. Wọn tun fẹ́ lati gbọ́ síi nipa bi mo ti se nrí àgbọ̀nrin ni àárin Ọgbọ̀n sí Ogòji ìsẹ́jú àti bi Ọlọrun ti se kọ́mi lati mọ iru ẹránko kan pàto ti máa ma rígbà níwọ̀n ti ìmọ̀ akọ tàbi abo bi ẹ̀dá ati ni ìwọ̀n bi ó ti tó. Mo ni lati gbà àwọn ìtàn nà ti mo rí ti ó nsẹlẹ̀ ti a fẹ́ ẹ̀ má gbàgbọ́, tí ó ba sì jẹ́ wipé a kòrí pé o sẹlẹ̀ bẹ́ẹ̀ ni, boya kò ba máa ya àwa nà lẹ́nu ni.

Lákòtàn, ọ̀sẹ̀ àti lọ sí Montana wọlé, Èmi àti Tim ni lati rin ìrìn-irìn àjò lati lọ pàdé àwọn aládari ti ẹgbẹ́ àwọn èniyan wọnyìí, àkópọ̀ àwọn ènìyàn nla ti wọn fẹ́ràn Oluwa. Wọn mú wa jádé lọ si ibití wọn ti má nyìn ìbọn lati ri àwọn ìbọn ti wọn ti pèsè silẹ̀ fún wa. Nitori ni Ohio ni mo ti dàgbà, Mi ò kọ àsà bi àti se nyìnbọn ni ọna to jìnnà. Yínyìnbọn mọ agbọnrín pẹ̀lú ìbọn kukúrú ni òfin fi àyè gbà àti jinjìn rẹ̀ ki sì ìjú ìwọ̀n ibùsọ̀ ọgọrun lọ, ọ̀pọ̀ igbà ni kìí jù ibusọ̀ ààdọta lọ. Nigbàti wọn bá wá

sètò afojúsùn ìbúsọ̀ igba silẹ̀ àtúnse ni yóò jẹ́ fun mi; lẹ́yìn ti mo bá ti gbáradi fún ìgbà diẹ, ma le sọ fún wọn pé mo ti setán lati lọ.

Ni àsálẹ́ ọjọ́ nà mo dá awọn tí ó wà ninú gbọ̀ngàn ile ìwé agbègbè lẹ̀kọ́, àti ni òwúrọ̀ ọjọ keji bakannà. Gbogbo àwọn arakùnrin na ni wọn retí àti gbọ́ àti nifẹ́ lati kọ́ nipa ìjọba Ọlọrun, páápa jùlọ, bí Ọlọrun ti se kọ́ mí ni òfin ti ìjọba rẹ nipaṣẹ sísọdẹ. Lẹ́yìn ounjẹ ọ̀sán, wọn sọ pé "Óyá bayìí ẹ jẹ́ ki a lọ lati wá a àgbọ́nrin." Mi ò ti dọdẹ fún agbọ̀nrin rí, mo si rò pé mi o si mọ bí wọ́n ti nseé. Ninú ìriri ti mo nipa ọdẹ síse, a máa njẹ́ meji tàbi mẹta lati lọ sóko ọdẹ, Sùgbọn ni tiwọn wọn gbé ẹkún ọkọ̀ mẹta si mẹẹrin àwọn ènìyàn lọwọ́. Mo ránti alẹ́ ó ku ọla ti Tim bi mi lérè pé, "baba mi, sé ẹ si ni ìfọkànbalẹ̀ lorí ọ̀rọ̀ àgbọ̀nrin yìí? Ẹ o kọ́ wọn nipa ìjọba náà àti pàṣẹ pẹ̀lú ìdanilójú pé kí ìjọba nàà máa siṣẹ nigbà gbogbo, sugbọ́n ti ẹ kò ba lọ rí àgbọ́nrín nkọ́ ti gbogbo wọ́n si ti pejọ ti wọ́n nwò?" Mo sọ fún wip mi ó jáyànipa rirí àgbọnrin. Drenda àti èmi ti gbin irúgbìn wa àsì ti ní adéhùn fún àgbọ̀nrin;yòó ti wà nibẹ̀.

Bi ati nwa ọkọ jáde lọ sí ọgbà ẹranko ti wọn fi àyè gbà fun sisọdẹ ẹran, wọn nsàlàyé pe àgbọ̀nrin ni ẹranko ti o yára ju ninú àwọn ẹrankò ni Guusu Amẹrikà àti ẹranko ti o yára jù sìkejì ni àgbáyé, ti o jẹ́ àmọ̀tẹ́kùn nìkan ni o tún yara jù ú lọ. Wọn ni àgbọ̀nrin máa nriràn dáadáa , ohun kan ti wọn fi máá dààbobo ara wọn nà ni eré sísá, torina ti wọn ba rí, ni àrin ìsẹ́jú kan wọ́n ti sálọ. Ohun ti èmi fọkan si ni akọ̀ àgbọnrin nla, ti Tim sin wọ àbo rẹ̀.

Èrò wa ni kí awa ọkọ̀ lọ si ọgbà ẹranko, sugbọ́n à lọ si ibi giga kan, àsi wà loke à nwo afonífojì to jin lati wòó boya à le rí awọn ẹranko nibẹ̀. Bi a ti nrìn kiri lokè nà a rí àwọn agbo àgbọ̀nrin kan lọ́ọ̀kankán. sùgbọ́n tori bi oju -ilẹ̀ na ti rí a wòó pé ó yẹ ki a súnmọ wọn diẹ ki a to yinbọn a wá ni lati rọra súnmọ́ wọn ti a o fi de ọrí òkè ti ó gbẹ̀yìn si ọ̀dọ̀ wọn diẹ diẹ àti rọra ni lati yin ìbọn mọ wọn ti wọn ba sì wà nibẹ̀ nigbà ti à o ba fi súnmọ́ wọn mú, Nikété ti a bati dé ibẹ̀, yóò gbà wa ni igba si àrínlélúgbà ibùsọ́ ti o ba ti wà ni ipò ti o yẹ

Èmi ati Tim a rọra nfàyàwọ́ ni ilẹ̀ fun ìgba diẹ lati le rì pé a súnmọ ọ̀dọ̀ wọn sí ibi igun oké nà ti a ti rí wọn. Nkan ti a rò nipe ti mọ ba ti yìnbọn tèmi tán, Tim nà yóò yin tirẹ̀ lù wọn. Mo wa rọra wọ́ sí etí ọ̀dọ̀ wọn mo si

ri wọn . Lótítọ́, èròngbà wa siṣẹ́; àwọn ẹranko wọ̀nyìí kò rí wa, mo gbé ìbọn mi, sugbọ́n kò fi bẹ́ẹ̀ rọrùn lati duro dáadáa lati ọ̀nà jinjìn, bẹ́ẹ̀ ni mo nmi léraléra nitori pé mo wọ́ nilẹ̀ de ibẹ̀ ni. sùgbọ́n lopin rẹ̀, ni gbàti mo ronú nipa akọ àgbọ̀nrin, mo fa ibọn mi mo sì yìn ín, ó tàse. o dabi wipe nkan ti onsẹlẹ̀ rú awọn ẹranko na lojú bi mo ti yìnbọn ẹlẹkejì. o tun tàse. Nibayi wọn ti nsún bi mo ti nyìnbọn ẹlẹkẹta si wọn ati ẹkẹẹrin gbogbo rẹ̀ ni o tàse. Bi mo ti yín ẹlẹkaarún, ohun ti mo gbọ́ ni tùẹ̀. kò sí ọta mọ.

Ninú gbogbo èyí awọn ẹranko ti túká wọn ti salọ wọn kò si ni tosí mọ́. Gbobo wọn ni yàtọ si èyí ti mọ ti nyinbọn mọ tẹ́lẹ̀. Mo wa dìde duró dáradára, ti kò jinnà si ibi ti mo wa tẹ́lẹ̀ ti mo ti yinbọ̀n àkọ́kọ́. Mo wa gbà ìbọn ọwọ́ Tim. Mo ti dìde duró bayìí, mo si yìn ìbọn mọ akọ ẹran na ó si subú lulẹ̀. Inú mi dùn gàn ara mi si wá balẹ̀ ni ìgbakannà. Akọ ẹran náà jẹ́ t'èmi. bi mo ti wọ ẹ̀yìn mi, o yàmilẹnu lati ri ẹgbẹ́ àwọn ọkùnrin wọnyìí ti wọn hoo yè àti se àjọyọ̀. àwọn kan wa lorí ẹ̀rọ́ alagbeká wọn mo esi gbọ́ ti ọkan ninú wọn nsọ pé, "Bẹ́ẹ̀ni, o dà bi ohun ti ọ wà ninú ìwé *Sísọdẹ ìgbàgbọ́* nà ni Kòju ogóji ìsẹ́jú na lọ akọ̀ agbọ̀nrin na si duró sibẹ̀, gẹ́gẹ́ bi o ti wà ninú ìwé nà". Gbogbo wọọn sì wá lati ri bi ìjọba Ọlọrun ti nsiṣẹ. Lẹ́yìn gbogbo rẹ̀, mo ti nkọ wọn fún bí ọ̀pọ̀ wákàti, wọn sì fẹ́ ríi bi ọ ti nsisẹ. Ó dára, ninú gbogbo aimọ ìbọn yìn náà, ó tun siṣẹ o si tún mú iyì ba ohun ti mo ti kọ́ wọn. Tim nà si ri àbo tirẹ̀ na ni ọ̀sán ọjọ nà pẹ̀lú ibọ́n ti o yìn mọ agbàrin nà. Àwa mejeji ni inu wa dún! Montana jẹ́ ibi tórẹwà gàn, èmi ati Tim na si jẹ̀gbádùn ìrírí ti ìjọba Ọlọrun nibẹ̀, Mo si ni orí agbọ̀nrin ti mo gbé kọ̀ sórí pakó ninú ofisì mi fún ìrànti ìjọba Ọlọrun àti jíjẹ́ olótítọ ati òdodo Rẹ̀.

**GBOGBO AYÉ NI ÈBI NPA LÁTI RÍ I OHUN KAN NÁÀ, ATI ÌFẸ́ ỌLỌRUN LÁTI YÀ WỌ́N LẸ́NU BÁKANNÀ.**

Kílódé ti máa fi sọ ìtàn sisọdẹ fun ọ ninú ìwé yìí? Nitori Ọlọrun fẹ́ lò ọ́ lati se afihàn ìjọba Rẹ̀ fún gbogbo àwọn ọ̀rẹ́, alábágbé àti ẹbi rẹ. Gbogbo wọn ni wọ́n fẹ́ rí pé o nsiṣẹ. Gbobo ayé ni ebí npa lati rí ohun gànnà, àti ìfẹ́ Ọlọrun lati yà wọn lẹ́nu bakannà. Láti yà wọ́n lẹ́nu, o wa ni lati mọ bi ìjọba Ọlọrun ti nsiṣẹ àti bi Ẹ̀mi Mimọ́ ti nmú àwọn ìdáhùn wá àti àwọn ànfàni ti o nilò lati yá gbogbo wọn lẹ́nu, kódà ara rẹ pẹ̀lú. Bi mo ti wá mọ̀ lẹ́yìn-ọ̀rẹ-yìn, pé àwọn arakìnrìn ti wọn sakóso ẹgbẹ́ nà mu mi wá sókè

fún idi to yàtọ̀ lati sàfihàn ìjọba Ọlọrun fún ọ̀pọ̀lọpọ̀ àwọn èniyàn ti wọn ti ba ara wọn ninú ẹ̀sìn. Mo wa gbọ̀ pé ọ̀pọ̀lọpọ̀ ni o ti fi ọkàn wọn fún Oluwa lati inú ìdanilẹ́kọ́ ọjọ́ nà. Bakannà Ẹ̀mi Mimọ́ ti sètò na silẹ́ atipé yóò ràn ọ lọ́wọ́ pẹ̀lú gbogbo ètò rẹ lati yọrísí rere.

Jẹ́ ki ntún sọ ìtàn kan fún ọ si, sugbọn èyí lati inú Bibeli ni masì tún sapejúwe bi Ọlọrun ti se fẹ́ lati yà ọ́ lẹ́nu pẹ̀lú àwọn ètò àti ìlànà ti yóò mú ẹ̀rí ìdanilójú òtítọ́ ati ìfẹ́ Rẹ́ si àwọn ti ó wà ni àyíká rẹ.

> *O sì se, nígbàti ìjọ ènìyàn sú mọ́ ọ láti gbọ́ ọ̀rọ̀ Ọlọrun, tí om si dúró leti adágún Génésárétì, ó rí ọkọ̀ méjì ti wọ́n gún létí adágún; sùgbọ́n àwọn apẹja sọ̀kalẹ̀ kúrò nínú wọn, wọ́n ńfọ àwọ̀n wọn. Ó sì wọ̀ ọ̀kan nínú àwọn ọkọ̀ na, ti íse ti Simoni, ó sì bẹ̀ ẹ́, kí ó tẹ sí ẹ̀hìn díẹ̀ kúrò ní ilẹ̀, Ó sì jókòó, ó sì ńkọ́ ìjọ èniyàn lati inú ọkọ̀.*
>
> *Bí ó sì ti dákẹ́ ọ̀rọ̀ ísọ, ó wí fún Simoni pe, Ti sí ibú, kí o si ju àwòn yín sí ìsàlẹ̀ fún àkópọ̀''*
>
> *Simoni si dáhùn ó si wí fún un pé Olùkọ́ni, gbogbo òru aná ni àwa fi sisẹ́ àwa kò si mú nkan; sùgbọ́n nitori ọ̀rọ̀ rẹ, èmi o ju àwọ̀n nà sí ìsàlẹ̀.*
>
> *Nítorí wọ́n sì ti se èyí wọ́n kó ọ̀pọ̀lọpọ̀ ẹja àwọ̀n wọn sì ya. Wọ́n sì sàpẹre sí ẹgbẹ wọn, tí ó wà ní ọkọ̀ kejì, kí wọ́n kí om wá ràn wọ́n lówọ́, wọ́n sì wá, wọ́n sì kún ọkọ̀ méjéjì, béni wọ́n bẹ̀rẹ̀ sí írì. Nigbati Simoni Peteru sì rí , ó wolẹ̀ lẹ́ba ekún esu, ó wí pé, Lọ kúrò lọ́dọ̀ mi ; nítorí elẹsẹ̀ ni mí , Oluwa.*
>
> *Ẹnu sì ya wọm n, àti gbogbo àwọn ti mbe. pẹ̀lú rẹ fún àkópọ̀ ẹja ti wọ́n kó, beni Jakobu ati Johannu awon omo Sebede, tin se alabakegbe Simoni.*
>
> —Luku 5:1-10

Peteru, Jakọbu àti Johannu ti fi gbogbo oru wá ẹja wọn kò si ri nkankan mú. Èyí ni ìrírí àwọn àgbàlagbà apẹja lori ọmi ohun ti wọn mọ̀

se dáradára, sibẹ̀ wọn o ri ẹja kan pa. wọn padà wá lọ́wọ́ òfo. sugbọ́n ìtan nà kó parí síbẹ̀. Jesu way á ọkọ̀ oju-omi ti Peteru lati fi wàásu lati inu rẹ̀ àti ki o si ti ọkọ̀ rẹ padà sinu ibú omi lati kó ẹja, Ó ya Peteru lẹ́nu, ó wa sàlàyé pé gbogbo òru ni awọn fi nsiṣẹ ti awọn nwa ẹja ti awọn kò si rí ẹja Kankan mú, sùgbọ́n nitori pé Jesu ni o sọ bẹ́ẹ̀, òun yóò ju àwọ̀n nà sinú ibú. Nigbàti Peteru ju àwọ̀n náàsinu ibú, Bibeli sọ pé ó si kó ọ̀pọ̀lọpọ̀ ẹja tí àwọ̀n rẹ si fàya, wọ́n si pé awọn ẹgbẹ́ wọn lati wá ràn wọ́n lọ́wọ́. Ìwe mimọ́ tun tẹ̀síwájú pé àwọ̀n ẹgbẹ́ wọn ti o wá lati ràn wọn lọ́wọ́ náà fà ya , wọn si kó ẹja ọkọ̀ mejeeji sì kún fún ẹja ti wọn sì nrì. Bibeli ni pé ẹ́nu si ya àwọn apẹ̀ja wọ̀nyí fún ọ̀pọ̀lọpọ̀ ẹja ti wọ́n kó ni ọjọ́ na wọn fi àwọ̀n sílẹ̀ wọ́n si tẹ̀lé Jesu.

Ọ̀kan lara àwọn ìtàn ti mo fẹ́ràn ninú bibeli niyìí nitori o se àfihàn àwòrán ìyàtọ̀ tí o wà láàrin àwọn ìjọba mejeejì, ìjọba ti òkùnkùn ati ìjọba ti Ọlọrun. Ìjọba ti òkùnkùn, Ìjọba ti Satani jẹ́ ti fífọ̀, àìní, ti fífi gbogbo òru wá ẹjá laìrí nkankan mú jade, kún fún irìn àjò ìnira, ìdaàmu ki o ma làágun lati le ráyégbé. mo pè é ni ìgbésí ayé ti a ti fi gégun. Ti Adamu mu wa nipa ìsọ̀tẹ̀ rẹ̀ si Ọlọrun, ki ó wa gbé e yẹ̀wó si ti àwòrán ti ìjọba ti Ọlọrun àti àwọn ohun ti o npèse. Fi oju inú wòó nkan meji yí, kí o wá wòó pé Ọlọrun ti fún ọ ni ìlẹ̀kùn ẹlẹkejì, Ìjọba náà.

Nibàyii gbogbo Kristiani ni yóò pariwo àti pàtẹ́wọ́ pé Bẹ́ẹ̀ni Ìjọba Ọlọrun tòbi; wo bi wọ́n ti ri ẹjá pa tó" Sugbọn àwọn diẹ yóò bèrè pé bawo ni Jesu ti seé, ati pé ọ̀pọ̀ ni kò si mọ̀ pé àwọn na ni iru àṣẹ yí kannà àti àgbara lati jẹ ìgbádun ìpèsè ni ìpele ti Peteru àti Jakọbu àti Johanu wà ni ọjọ́ náà. Àlayé ti o yẹ wa fún ìdáhùn bi pé bawo ni Jesu ti seé, ohun tó se ni ọjọ́ nà ni ohun ti ó le sé nitori Óun ni Jesu. Sùgbọ́n dúró na o; a ti rí tẹ̀lẹ̀ pé Jesu kò le mu gbogbo èniyàn láradá ninu ìwe Maaku ù nitori ọ̀run kò ni agbara ni bẹ̀. Rárá, àwọn òfin t'ẹ̀mi wà bi àwọn ìjọba nàà ti nsiṣẹ ni ọjọ́ na ti o pèsè àwọn ẹja ti mu.

Sugbọn ohun ti o sẹlẹ̀ nìyìí. Ọ̀pọ̀ àwọn Kristiani ti mo ti ba pàdé wọn o tilẹ̀ róò rí pé ó se ése lati se ohun kannà ti Jesu se, pé ti wọn bá seé, wọn ò mọ̀ àmì ti o fi se wọn. Mo máa nlo gbolóhùn ọ̀rọ̀ kan ninú awọn ìpàdé mi gbogbo pé ti o kò bá le kọ́ní nkankan, ìwọ na kò le ni nkannà. Ohun ti mò nsọ ni pé ti o kò ba le sọ bi ọ̀rọ̀ ẹja ti se sẹlẹ̀, o kò ni le sọ ẹ̀dá ohun ti o sẹlẹ̀ nà. Báwo wá ni nkan nlá ti wá sẹlẹ̀? Sé o le sàlàyé rẹ̀? Ti ìwọ náà ba

fẹ́ ni ìru àseyọrí nlá yìí, o ni lati mọ̀ bi àwọn ẹja na ti se wá. Sibẹ̀síbẹ̀, ọ̀pọ̀ àwọn ènìyàn ni o má nyàlẹ́nu ti mo bá nsọ̀rọ̀ báyìí. Sùgbọ́n kínni ohun ti Jesu sọ?

> *Lóòtọ́, lóòtọ́ ni mo wí fún yín, eniti ó bá gbà mim gbọ́, isẹ́ ti mo se ni òn nà yomò se pẹ̀lú. Isẹ́ ti ó tóbi ju wọ̀nyìí lọ ni yóò se, nítorí èmi ńlọ sọ́dọ̀ Baba.*
>
> —Johannu 14:12

Nigbàti Jesu ní kí a se iṣẹ yìí kan nà ti òn ti nse nitorìtí Ón nlọ sọ́dọ̀ Baba, Ó nsọ́ niti Ẹ̀mi Mimọ́ tí ó nbọ̀ sórí wa lẹ́yìn ikú àti àjinde Rẹ̀. Ẹ̀mi Mimọ́ yi kannà ni o ba lé nigbàti Ó wà ninú odò Jordani, ti ò ràn án lọ́wọ́ lati fi agbára nla Ọlọrun hàn ti a nrí ti a bá ti tẹ̀lé iṣẹ ìránsẹ́ Rẹ̀. Nigbàti a si ti mọ̀ pé wọn di agbára yìí lọ́wọ́ ninú ìwe Máàkù orí kẹfà nitori tí àwọn ènìyàn náà kò gbàgbọ́, sibẹ̀, ninu ìwe Lúkù ori kaàrún a kò dí agbára náà lọ́wọ́ lati kó ọpọ̀ ẹjá, ani lati mọ̀ nipa òfin ti ìjọba Ọlọrun kí à ba le pinnu ohun ti ó le sèdíwọ́ tàbi ohun ti ó le mú kí agbára Ẹ̀mi Mimọ́ rọrùn lati rìn kọjá ninú ipòkípò ti a bá wà. Torinà, ẹ jẹ́ kí a lo wo ìtàn kan kí a si wòó bi a ba le lo òfin àti ìlànà ti a le mọ̀ àti kọ́ ẹ̀kọ́ lati ibẹ̀.

Nibayìí, ti o bá jẹ́ wípé o ti ka ìwé mi alákọ́kọ́, wà ti mọ ohun tí ó sẹlẹ̀ ninú ẹ̀mi nibíyìí nigbà ti Peteru fún Jesu ni ọkọ̀ ojú ọmi rẹ̀ lati lò. ọkọ̀ Peteru, àní gbogbo okòwò iṣẹ ẹja rẹ̀ ti o nse ni o mu àyípadà ba ìjọba àti gbogbo sàkaní-agbára rẹ̀! Bẹ́ẹ̀ni, nigbàti Jesu ti gba ọkọ̀ na lọ́wọ́rẹ̀ fún iṣẹ ìránṣẹ Rẹ̀, ni ọkọ̀ Peteru ti wà ni sàkáni-agbára ti ìjọba Ọlọrun. Ni keté ti ọkọ̀ na ti bọ́sí sàkáni -agbára ti Ọlọrun, Ẹ̀mi mimọ́ ni ẹ̀tọ́ labẹ́ òfin lati gba ọ̀rọ̀ ìmọ́ ti Jesu sọ lati múu lọ si ibiti àwọn ẹja wọ́pọ̀ si ninù ibú omi. Ọ̀pọ̀lọpọ̀ ẹja ti wọn ri kò jẹ́ èsi abájade ti wọn rí jẹ́ ipinu àti ète ìlànà ti o kọjá òye èniyàn nipa Ẹ̀mi Mimọ́ fún Peteru nigbà ọjọ́ Jesu. Ìmọ̀ ìkọ̀kọ̀ ni mo pèé, nitori nkan yìí Peteru, Jakọbu, àti Johannu sì rí ọ̀pọ̀lọ̀pọ̀ ẹja ti wọn o tírí irú rẹ̀ rí kó ni ọjọ́ nà. Kódà , Bibeli sọ pé ó si ya àwọn apẹja nà lẹ́nu.

Mo gbàgbọ́ pé Jesu fẹ́ kí ìwọ́ náà ma gbé ìgbésí ayé ti o yanilẹ́nu. Mo si mọ̀ pé ọkọ̀ oju omi ìgbàgbọ́ tí ó wà lófìfo kò le mu àwọn èniyàn wá sọ́

dọ̀ Ọlọrun. Ọlọrun fẹ́ kí àwọn èniyàn rí rere ti ìjọba Rẹ̀ ki gbogbo ènìyàn le ríi àti gbàgbọ́ pé Ọlọrun ti ó dára ní ti o sì fẹ́ latí gba gbogbo àwọn ti o ba wá sọ́dọ̀ Rẹ̀. Wolii Aìsaya sọ nipa èyi nigbà tí o nsọ́rọ̀ àsọtẹ́lẹ̀ ti nsọ nipa ìjọ.

"*Kí á le pè wọ́n ní igi òdodo, ọ̀gbìn Olúwa, kí a le yìn ín lógo* (Aisaya 61:3b).

Nítorínà, kínni ohun tí mo fẹ́ kí o mọ́ nipa ìtàn ẹja lati inú ìwe Lúkù ori Kaàrún? Bakanna, ọ̀pọ̀ àwọn nkan t'ẹ̀mi ni o le rí mú jáde ninú itàn na, ti o bá le mú àwọn nkan yi lò, yóò yí ayé rẹ padà.

**Ẹnikẹ́ni ni o le pa ẹja ti Jesu ba sọ́ fún wọn ibiti gan ti wọn ó ju àwọ̀n wọn sí**! **Tabi ẹ jẹ́ kí nsọ́ bayìí pé: Ẹnikẹ́ni ni o le pa ẹja ti Jesu ba sọ fún wọn ibití àwọn ẹja nab á wà àti bi wọn yóò ti se pa wọ́n.**

Awọn ènìyàn nsọ fún mi pé "Ò dara bi o ti sọ, Gary, sùgbọ́n Jesu kò si nibíyìí mọ́" Rara, sùgbọ́n Ẹ̀mi Mimọ́ kannà ti ó sọ́ fún un ni ọjọ nà ibiti àwọn ẹja wà si wà nibiyìí loníí o sì ngbẹ̀ inú rẹ ti ó ba jẹ́ onígbàgbọ́. Gbọ́ ohun ti Jesu sọ́ fún àwọn ọmọ ẹ̀yìn Rẹ̀ nigbà ti o ngbàràdì lati fi wọ́n sílẹ̀ lọ.

> *Nkan wọnyìí ni èmi ti sọ fún yín, nígbàtí mo mbá yín gbé. Sùgbọ́n Olùtùnú nà, Ẹ̀mí Mímọ́, ẹnití Baba yóò rán ní orúkọ mi, òn ni yóò kọ yín ní ohun gbogbo yóò sì ran yín létí ohun gbogbo ti mo ti sọ fumn yín. Àlàáfìà ni mo fi sílẹ̀ fún yín, àlàáfìà mi ni mo fifún yín : kì íse gẹ́gẹ́ bí ayé iti fi fún ni, ni èmi fifún yín. Ẹ máse jẹ́ kí ọ̀kan yín dàru, ẹ má si jẹ kí ó wárìrì.*
>
> —Johannu 14:25-27

Kínni àlàáfìà Jesu? Ẹ̀mi Mimọ́ ni o sọ fún bi yóò ti sese nigbogbo ìgbà ti ó ba ti ni ohunkóhun ti o bá fẹ́ se. Jesu pe Ẹ̀mi Mimọ́ ni Olútùnú, Ọ̀rẹ́, Olùtùn yìí ngbé inú rẹ kò sì le fi ọ́ sílẹ̀. Sé ò ntẹ́tí gbọ́ ohun tí Ó nsọ? O ni lati gbà pé Ọlọrun ni ìdáhun si ipòkipò ti o ba bá ara rẹ. Jesu sọ pé Olùtùnú yí le kọ́ ọ tbi fún ọ ni ìmọ̀ràn lorí ohun gbogbo. Gẹ́gẹ́ bi *Strong's Exhaustive Concordance of the Bible* (3875), Bí ìsọ̀kàn tógbórà nikikún

ti inú Bibeli(3875), ni itúmọ èdè Giriki ohun ti Olùtùnú túmọsí ní: ẹni ti a pè tàbi pew á sọ́dọ̀ ẹnikan, pàápàá pè lati ranni lọ́ wọ́. Ótún tùmọ̀ si ẹni ti o nbẹ̀bẹ̀ fún ẹlomiràn niwájú adájọ́, imoràn bi olugbéja, agbẹjọrò, tàbi alágbàwi. Ni ọ̀rọ̀ kan, ó túmọ si olùrànlọ́wọ́, ẹnití o sàtilẹ́yìn fún ni,

**JESU PE Ẹ̀MI MIMỌ́ NÍ OLÙTÙNÚ. ỌRẸ́ OLÙTÙNÚ YÌÍ NGBÉ INÚ RẸ KÒSÌ LE FI Ọ́ SÍLẸ̀.**

Èmi o mọ̀ nipa tìrẹ, mo le lo irú olùrànlọ́wọ́ yìí; ìwọ nkọ́? Ẹ̀mi Mimọ́ ni ìdáhùn Peteru nigbàtí o fi gbogbo oru siṣẹ lárí ẹja pa, Ẹ̀mi Mimọ́ yìí nàà sì ni ìdahùn tèmi na nigbàti mi o mọ ibiti ma ti rí owó. Mo ni lati jáde kúrò ninú oko gbèsè. Lẹ́yìn ti mo ti kò gbogbo ẹbi mi sinú ẹgbin yìí fún ọ̀pọ̀ ọdún, nigbàti mó kọjú si Ọlọrun fún ìrànlọ́wọ́, Ẹ̀mi Mimọ́ yìí ni o fún mi ni àla ni oru ọjọ́ kan lati kúrò ni ile iṣẹ́ ti mó nbá siṣẹ́ àti lọ bẹ̀rẹ̀ ìṣẹ́ tèmi nà lati ìbẹ̀rẹ̀.

Ẹ̀mi Mimọ́ ni ó sọ fún mi pé ile iṣẹ́ ti mo fẹ́ bẹ̀rẹ̀ yìí wà lati kéde rere ti Ọlọrun àti lati le ma ran  àwọn ènìyàn lọ́wọ́ jade kúrò ninú oko gbèsè, ti o jẹ̀ ni iru àsikò na ó jẹ́ èrò asiwèrè ti mo tí nírí. Èmi lati ràn àwọn ènìyàn jadé kurò ninú gbèsè?  Ó dabi eré ọmọde ti kò mọ ohun tí yóò fowó se. Èto ìsunà mi dàbi àlá. Sùgbọ́n ohun ti ó sọ pé kin se nìyìí, Nipa ìgbàgbọ́, èmi àti Drenda bẹ̀rẹ̀ àwa nà se ohun Peteru se nigbànà. "Oluwa, nkan yìí kò mọ́gbọ́n dáni, sìgbọ́n nitoriti o ti sọ bẹ́ẹ̀, à o seé"  Nitoriti à tẹ̀lé ìmọràn ti Ẹ̀mi Mimọ́ ile ìsẹ́ ti à sẹ̀sẹ̀ bẹ̀rẹ̀ ndàgbà on si ndàgbà o sì nmú owó ti èmi àti Drenda fin san gbèsè wa jáde titi a fi san gbèsè na tán pátápátá. Ile iṣẹ́ na si wà titi di òní,  nibáyìí o ti pé ọgbọ̀n ọdún. sẹ́yìn ó sì tún mú ẹgbẹ̀lẹ́gbẹ́ dọlla wá bi èrè ni ọdọdún.

Hey, Ki ise pé èmi lógbọ́n jù tàbi ìwọ, sugbọ́n Ọlọrun ti fún ọ ni Ẹ̀mi Mimọ́ lati le ran ọ lọ́wọ́ pẹ̀lú àwọn ìdahùn ti o nilò ninú ayé rẹ. Sùgbọ́n bi a ó ti ma kọ́ ẹ̀kọ́ ninú ìwe yìí, àwa na ni ojúse tiwa láti se, ni rínrìn pẹ̀lú Ẹ̀mi Mimọ̀ lati mu kí ìfẹ́ Ọlọrun wá sí musẹ.

Ó ṣe ni láànu, ninú àwọn ìrírí mipẹ̀lú àwọn ènìyàn, ó dàbi ẹni pé ọ̀pọ̀ Kristiani ni kò ri ìdáhùn si àwọn ìṣòro ti wọn kojú ninú aye.  Wọ́n kan nse ohun gbogbo lọ ninú agbára wọn ni, lẹ́yìn ti wọn bá ti fi gbogbo òru wá ẹja tán wọn ó tun máa padàbọ̀ lọ́wọ́ ófo tabi palẹ̀rẹ̀mọ́. Wọn kò ti gbọ́ rí pé Ẹ̀mi Mimọ́ wà nibẹ̀ lati ràn wọn lọ́wọ́ ninú gbogbo ipo ti wọn ba wà.

Biotìlẹ̀jẹ́pé, ọ̀pọ̀ àwọn Kristiani ni o ma nsọ pé, Ọlọrun yóò rànmilọ́wọ́ lati se èyí tàbí tọhún" sugbọ́n wọn kò ni oye bi yóò ti se ìrànlọ́wọ́ nà, tàbi bi wọn yóò ti gbọ́ ìdahun ti wọn nilò. Ọ̀pọ̀ ni kò mọ̀ pé àwọn nilò lati siṣẹ́ pẹlú Ọlọrun ki wọn ba le ri ìdahun ti wọn ti ndúró dè, bẹ́ẹ̀ni wọn si tún dúró de Ọlọrun lati se nkan nipa ìsoro ti wọn ni, nigbàti ìdáhùn ti wà ninú wọn.

Nípa ọ̀rọ̀ ti owó, fún àpẹẹrẹ, àwọn ènìyàn yoo má sọ pé Ọlọrun yóò mu mi serere. Mo ni "Ó dára! Bawo ni Ọlọrun yóò ti se jẹ́ kí owó na de ọdọ̀ rẹ? Akọ́kọ́, wọn ó binú pé mo bèrè irú ìbérè yìí lọ́wọ́ wọn bi igbà ti mo nwádí ìgbàgbọ́ wọn. Sugbọ́n mo sì tún bèrè. "Níbo ni owó na yóò ti wá? Bawo ni Ọlọrun yóò ti se mu owó náà tọ̀ ọ́ wa? Nigbàti mo tẹnumọ bí bèrè ìbèrè yìí lọwọ́ wọn, wọn kò mọ̀. O seése ki ènìyàn má mọ̀ fun ìgbàkan, sugbọ́n síbẹ̀, o nilò lati ní ìdáhùn. O kò le kórè ohun tí o kò rí. Ránti, Jesu sọ ni pàtó, nigbàti ó sọ fún Peteru ibiti àwọn ẹja wà, o si tún sọ fún un bi yóò ti se ri wọn mu; "ju àwọ̀n rẹ si inú ibu" Bakannà, o nílò lati mọ̀ ibi ti wà ju àwọn rẹ si ti o ba fẹ́ lati mú ẹja.

Nitoriti àwọn èniyàn ni nkan ti mo pè ni lakáàyè ti àpótí ìkowé rànṣẹ́, ti wọn yóò kan ròó pe Ọlọrun yóò se ni, ti o si jẹ́ wipé ojukannà ni ètò ìsuná wọn wà lati bíi ọdun mẹwa tàbi ogún ọdún ti kò si yípadà. Ó jẹ́ ohun ti o bani lọkànjẹ́. Se o fẹ́mọ idi ti wọn fi wà bakannà? Nitoripé wọn ò ti kọ́ wọn bi wọn ti se le máa pa ẹja ni ọna ti Ẹ̀mi Mimọ́, ni ọ̀nà ti ìjọba ọ̀run. Wọn ò ti mọ̀ bi Ẹ̀mi Mimọ́ ti nsiṣẹ́ lorí ilẹ̀ ayé lati mú wọn laseyọrí. Wọn ó ti mọ ojúse ti wọn lati se àti ipa tí Ẹ̀mi Mimọ́ yóò kò lat le jẹ́ ki wọn ni àseyọrí ti wọn nilò ni kiakia.

Ó dàbi àràkunrin ti mo rí lọ́san ònìí. Ó tóbi gàn, o wọ̀n tó ìwọ̀n 375 pọùn. Ó ni ẹ̀wọn kan ni ẹsẹ́ kan ati ni ọ̀pá mejì pẹ̀lú rẹ. Kò le rin. Lẹ́yìn ti o jẹ́ Bọgà rẹ́ tán, o tun bèrè fun paii ti àfi ẹ́pá se. Kódà, ìyàlẹ́nu ni ó jẹ́ fún mi nigbati mo gbọ pe ó nbèrè fún paii yi. Mi ò mọ ohun tí o nrò, sugbọn paii tí ó wà ni ọwọ́ rẹ́ titó, wọ̀bìa ni, o sì npa lọ. Ó jijakadì ni kí ó tó le dìde nibiti o jóko sí, pẹ̀lú ìnira, ni pẹ̀lẹ́pẹ̀lẹ́ ni o fi jade kúrò ni ile ounjẹ nà. Bi mo ti ríi tí awọn Kristiani se ngbé lode ònìí niyìí—wọn yóò gbọ́ awọn ìlérí, wọn o si tún tẹ̀síwájú lati tún máa jẹ ohun olóró/ tàbi Majele, yóò wa máa yà wọ́n lẹnu idi ti nkan kò se lọ́ déédé fún wọn.

Ọ̀rẹ́, o ti ni ìdáhùn! Ẹ̀mi Mimọ́, Ọlọrun tìkararẹ̀, ngbé inú rẹ lati pesè

**EMI MIMỌ, ỌLỌRUN TÌKÁRARẸ̀, NGBÉ INÚ RẸ LÁTI PÈSÈ ÌDÁHÙN KÍDÁHÙN TÍ O LE NÍLÒ.**

ìdáhùn kidáhùn ti o le nilò. Awọn èníyàn nbèrè lọ́wọ́ mi bóyá wọn le fẹ́ Susan tàbi Sally, bóyá ki àwọn gba ìṣẹ́ kan tàbi kí àwọn ma gbàá, bóyá ki awọn duró tabi kí àwọn máa lọ, tàbi ki awọn dúró si ibi ti awọn wà, ta ọjà wọn tàbi ki awọn ra ọjà miràn, Ẹ̀mi Mimọ́ ninú rẹ ni ìdáhùn si gbogbo àwọn ìbérè wọ̀nyìí. Atipé, ìdí ti a fi kọ́ ìwe yìí na nìyìí, lati kọ́ ẹ̀kọ́ bi Ẹ̀mi Mimọ́ Ti se le ràn wá lọ́wọ́ bi ìjọba Ọlọrun ti se nsiṣẹ́ nipa bi a ti se le máa gbọ́ ohun ti Ẹ̀mi Mimọ́ se.

Óyá jẹ́ kin tún gbé yẹ̀wò:

**Ẹnikẹ́ni ni ó le pẹja tí Jésù bá ti sọ fún wọn ibití àwọn ẹja nà wà àti bí o tise le mú u wọn, kódà àti ìwọ nà!**

Karol sàlàyé bi ayé rẹ̀ ti se yípadà ninú Ìmeeli ti o fi ránsẹ́.

*Ní ọdún tí ó kọjá lọ, ní àyájọ́ irú ọjọ́ òníí, Mo ńra àwọn ẹ̀bùn ọdún Kérésìmésì pẹ̀lú káàdi ẹ̀yáwó mi láwìn, mo sì wá gbé gègem le nitorí kòsí owó lọ́wọ́ mi lati fi ra ẹ̀bùn fún ọmọ mi obìnrin, tí ó fẹ́ lọ wo baba kéresì. Nínú àníyàn àti ìkorò ọkàn ni mo wà, mo wá kọ ìwé ránṣẹ́ si Pásítọ̀ Garry pé lóòtọ́ ni mo ńfúnrúgbìn ti ìgbadgbọ́ sùgbọ́n kò sisẹ, nkankan kò sẹlẹ̀: Pásítọ̀ si fi sùúrù àti pẹ̀lẹ́pẹ̀lẹ́ dámilóhùn pé, kín si nísùúrù pé ìkórè si mbọ̀ o maa ńgba àsìkò díẹ̀, kì ìse pé ní ọjọ́ kejì ni yoò sẹlẹ̀.*

*Lónìí bayìí, mo ti ra ẹ̀bùn fún gbogbo àwọn ẹbí mi pẹ̀lú owó lọ́wọ́ mi. mo sì fẹ́ ra ẹ̀bùn ti ó tó ẹgbẹrúnọdúnrún pọ̀ùn tàbí irinwó pọ̀ùn, mo sì ńfi ọlá fún àwọn ti o rànmílọ́wọ́ ní àkókò ìsoro. Ní ọdún tó kọjá, inú àjà ilẹ̀ ni mò ńgbé ibití àwọn ọrẹ mi kán fún mi láyè sí láti máa gbé fún ìgbà díe. Ko tilẹ̀ sí owó lọ́wọ́ mi tí mo le fi jẹun tàbí ra epo pẹntiro. Sùgbọ́n nibayìí mo ti ńgbé ilé tó dára àti rẹwà, ẹ̀rọ̀ amúomi tutù mi sì tún kún fún ounje.*

*Ní ọjó kẹta osù kejìlá ọdún ni ọjọ́ ìbí ọmọ mi obìnrin,a sì lọ sí ibùdó Hershey ni Pennysyvania. A pe awọn ọrẹ rẹ̀ láti wá pẹ̀lú*

*wa a sì wà ní ilé ìtura nà, a san gbogbo owó ohun tí a rà. Mo sì ra àwọn ẹbùn tí ó tó irinwó pọ̀n fun un tí ó sì jẹ́ wípé ní ọdún tí ó kọjá ẹnìkan tún dójúti mi tàbùkù nítorí ẹgbẹ̀rún pọ̀n tí ó fún mi láti fi se ayẹyẹ ọjọ́ ìbí re.*

*Mi ò le kọ ìwé yìí lái sunkún. Mo dúpẹ́ lọ́wọ́ Pásítọ̀ Garry àti ìyàwó wọn, Drenda. Ọdún yìí ni ó jẹ́ ọdún tí ó dára jùlọ nínú ayé mi. Àwọn ǹkan tí Ọlọrun se nínú ayé mi jẹ́ ìyanu, Mo le kọ odindi ìwé lórí gbogbo ìtàn ayé mi. O seun fún àwọn ẹ̀kọ́ tí o kọ́ mi pé mo le máa gbé ayé mi bí ẹnití ó wà lọ́run nínú ayé.*

Imeeli tí o kà tán yì jẹ́ ọ̀kan nínú àwọn ìtàn èyítí ó yanilẹ́nu ti inú ìjọba tí mo tì gbọ́; Sharon Michigan ni ó kọ ọ́ ránsẹ́.

*Pásítọ̀ Garry, mo ńkọ ọ̀rọ̀ ẹ̀rí yìí nítorí ti ọkọ mi ni àti èmi nà pẹ̀lú. Mo kàn fẹ́ dúpẹ́ lọ́wọ́ yín nítorí ìwọ àti ìyàwó rẹ jẹ́ ìwúrí fún wa. A gbọ́ nípa yín lórí Sid Roth ní bí ọdún mẹ́ta sí mẹ́rin sẹ́yìn. Ní àsìkò tí a la àwọn ìsòro kan kọjá. Wọn ti dá ọko mi dúró lẹ́nu isẹ́ lẹ́yìn ọdún mejìdínlógún, a sì sẹ̀sẹ̀ bẹ̀rẹ̀ ś kọ́ ilé ti ara wa ni tí ó tó ọ̀rìnlénígba pọ̀n nígbàtí ó sẹlẹ̀. Asì wọnú gbèsè àti ìdààmú..*

*Awá lọ ra àwọn àgbàsílẹ̀ ohùn isẹ́ ìránsẹ́ yín , ó sì ràn wá lọ́wọ́ láti la ìsòro náà já. A kọ́ bí gbèsè ti se le kóbá ìlera àti ayé ènìyàn ní kíákíá. A kọ̀ tilẹ̀ rí ọ̀nà àbáyọ. Bíotilẹ̀jẹ́pé a kò rí owó san fún ilé titun míràn, a sì gbé ibití a wà fún bí ọdún mejì kí am to kó jáde. Ìbudkún ni ó tumn jẹ́ fún wa ní ayè ọ̀tọ̀.*

*Kín wá gé ìtàn mi kúrú, ọkọ mi tún rí isẹ́ rẹ̀ gbà padà lẹ́yìn ọdún mẹẹrin tí ó ti dúró síle pẹ̀lú ìgbàgbọ́ ti ó sì gba àwọn ìleri Ọlọrun gbọ́ àti pẹ̀lú ìrànwọ́ ìwọ àti ìyàwó rẹ bí a ti ńgbọ́ àwọn isẹ́ ìránsẹ́ yín nínú CD. Ọkọ mi rí isẹ́ rẹ̀ gbà padà tí wọ́n sì san gbogbo owó ọdún mẹ́rin ti wọn fi dáa dúró fún un! Kò sì ní ọwó ilé ẹjọ́ kan nínú. Ó tún gba gbogbo àsìkò ìsinmi tí ó yẹ kí ó gbà ní adrin ọdún mẹ́rin nà, ohun àkọ́ko tí wọ́n ni kí óse ni kí o lọ fún ìsinmi ránpẹ́!*

*Bayìí a le san owó ile tí ó tún dára ju èyi tí a kúrò níbẹ̀ lọ nínú àwọn owó tí wọ́n san fún wa. Ẹ seun fún ohun gbogbo tí e se.*

Lati odo Andrew ni Missouri.

*Ní bí ọdún mejì sẹ́yìn nínu osù kaàrún, mo wà nínú ipò kan tí kò tẹ́milọ́rùn. Inú mí kò dùn sí isẹ́ kan tí mo tí ńse tẹlẹ̀ mo wá gba isẹ́ titun míràn bí alágbàtà. Àwọn a bá ni gba owó ńpè mí mi ò ti lẹ̀ ní owó lọ́wọ́ ti mo fẹ́ san, mi ò ni owó ti mo fẹ́ fi jẹun tàbí ra afẹ́fẹ́ gáàsì, osù si tí ńparí lọ tí máà tún san owó ilé ni kiákiá. Ohun tí MO SE nipé mo lọ kó àwọn CD tí Garry se jọ àwọn àkásílẹ̀ ohùn láti Ìyípadà 2.0 ní sísẹ̀ntẹ̀lé. Mo wà nínú ìsìn ní ọjọ́ kan mo sì fẹ́ dá owó ọrẹ, sùgbọ́n owó tí mo ní jẹ́ pọ̀ùn metàlélógún tí kò sì le gbé mi di òpin ọ̀sẹ̀. Isẹ́ sì nìyìí kò se dáada, mo sì jẹ́ ki Ọlọrun mọ̀ pé mo fẹ́ dá ọrẹ, sùgbọ́n kò sí owó ní ọwọ́ mi tó. Mo sì gbọ́ ohùn kan tí ó wá lati inú mi wá tí ó sọ pé Èmi (Ọlọrun )le se ọ̀pọ̀lọpọ̀ pẹ̀lú pọ̀ùn mẹ́tàlélógún ju ohun tí o le se lọ. Ọlọrun ni ó jẹ́ kin fi ogún pọ̀ùn sílẹ̀ mo sì gbà à gbọ́ pé yóò da padà ní rere.*

*Ní ọjọ́ Àlàmísì na, mo ń ran ẹnìkan lọ́wọ́ lẹ́nu isẹ́ tirẹ̀ láti síro isẹ́ tí ó ńse. Ó wù mí láti ràn án lọ́wọ́ laijẹ́ pem mo fẹ́ láti gba owó kakan kódà ti mo bá ta ọjà. Nígbàtí a setán ní ọjọ́ nà. alábójútó mi sọ pé inú òun dùn ti mo ba sisẹ́ àti pé kín máa kó gbogbo èrè orí ọjà ọjọ́ nà lọ(irú rẹ̀ kì sẹlẹ̀ bẹ ti ó bá ǹya ọ́ lẹ́nu). Wá woo pé kínni? Àpapọ̀ èrè ọjọ́ nà ti mo gbà wá jẹ́ ẸGBẸ̀RÚN MÉJÌ PỌ̀ÙN!!! Haà ÌLÓPO NÍ Ọ̀NÀ ỌGỌ́RÚN láàrin ọ̀sẹ̀ kan!*

*Ọlọrun jẹ́ olótítọ́, ọ̀pọ̀ ni nkan kékeré tí Ọlọrun bá fọwọ́si. Láti ìgbàna lọ, ni mo ti ń se ìfifún ni mi bí ologbọ́n,idámẹ́wa mi, ọre pẹ̀lú ínú didùn àti riretí ìdàgbásókè.*

*Lẹ́yìn bí osù meló tí ó sẹlẹ̀, ni mo ni ìgbéga sí ipò ti mo ti ńgbàdúrà fún GAN ohun tí mo ti ìtorí rẹ̀ dá ọrẹ irúgbìn. A gbé mi lọ sí bi ìpele kẹrin sí ibiti mo wà tẹlẹ̀ tí owó osù mi sì tún rúgọ́gọ́ si*

*lárin ọdún méjì. Ẹyin Ọlorun lógo, òn sì ni gbogbo ògo yẹ. Ìyìn ni fún orukọ rẹ̀: banki kò gba móto mi mọ, mo ti ni ọkọ̀ tuntun míràn ti mo nsan OWÓ Rẹ̀!!!.*

Ìroyìn ìyìn lati Korea:

*Pásítọ̀ Garry mi ọ̀wọ́n,*

*Ayé tí kò ní ìdí ni mò ngbé, tí mi ò sì le dá ohunkan se fún ara mi. Mo máa ntọrọ kiri ni, nígbàtim ọrọ̀ mi sú àwọn èniyàn láti máa rànmí lọ́wọ́, ohun tí o kù ni kín rí Bisikiti kan àti ọtí ẹlẹrìndòdò kan (kooku ati akara oyinbo). Nkan ti agbára ká lati rà fún èmi ati àwon ọmọ mi lati jẹ. Mi o le san owó ilé tàbi àwọn owó míràn san. Mo sì tún ranti igbatí mo si ńwo ètò ilé isẹ́ ìránsẹ Faith Life Church lórí afẹ́fẹ́. Mo wa se àlàyé fun pásítò kan ipò tí mo wà àti bi gbogbo nkan serí gbogbo ohun ti o fi dá mi lóhùn na ni pé mo ni lati bi Ọlọrun lérè lati fihàn mi bi ma ti se àti ibi ti mo ti le ri ẹja pa bi o ti se fi han Peteru ibi ti yóò ti ri owó orí san. Kín ge ìtàn na kuru, Mo ti ni ilé ounjẹ kan ti wọn pè ni ilé ounje African ati ibiti wọ́n ti ńgerun, nitori ti mo ńgbọ̀ ọrọ̀ ifiránsẹ́ ti ìdánilẹ́kọ pásitọ Garry. Ìyìn mi ni fún Ọlọrun!*

Wọnyìí ni ninú àwọn ìtàn nla! O le sọ pé, " nkan nla ni èyí, Gary. Bẹ́ẹ̀ni loòtọ́ , o nsiṣẹ́ fún àwọn kan sugbọ́n ki ise fún èmi" Ó dára, Ìtàn ti kò ti tán! Jẹ́ ki nbi ọ lérè nkan yìí. Bi o ti jokò ti o nka ori ìwe yìí, se o ndi mọ àga ti o fi jóko pẹ̀lú ìbẹ̀rù pé o ma le lefò? Rárá, kò rí bẹ́ẹ̀. Kílódé? Nitori o ni òye òfin ohun ti o lọ sọ́kè ilẹ̀ lonbọ́, O si mọ̀ pé bákannà ni ó ti nsisẹ́ fún ẹnikẹ́ni. Bẹ́nani, Ìjọba Ọlọrun ti nsisẹ́ lọnà yìí kanna. Ọ le kọ́ àwọn òfin, O le kọ́ lati gbọ́ àwọn ìlànà ètè ti ó le yí ayé rẹ pádà di ìtàn agbára ti Ọlọrun. Ati fi ìdì òdòdo múlẹ̀ ti nse ìwoye ti Ẹ̀mi Mimọ́ àti ìrànlọ́wọ́ ti o ti mú wá sinú àwọn ìtàn ti àti gbọ́ lọ. Nitorina, ẹ jẹ́ kí à bẹ̀rẹ̀ ìrìn àjò pélu àtúngbéyẹ̀wò àwọn kókó ti Ẹ̀mi Mimọ́, nigbànà ni à o wàà bọ sí ibi àlàyé lẹ́kúnrẹ́rẹ́ lorí gbigbọ́ àwọn ìlanà ètè ti a nilo.

ORI KẸRIN

# ÀWỌN ÌPÌLẸ̀: MÁ KÚRÒ NÍLÉ LÁÍSÍ ÀWỌN NKAN WỌ̀NYÌ

Tí bá fẹ́ máa gbé ayé ti o kún fún ìlànà ète ti Ẹ̀mi Mimọ́ àti ìdarí ti Ẹ̀mi Mimọ́ si ayé aségun, àkọ́kọ́ ná, ó ni lati di àtúnbi, ẹlẹkejì, ìrìbọmi ti Ẹ̀mi Mimọ. Bẹ́ẹ̀ni, iṣẹ́ ọ̀tọ̀tọ̀ meji ti Ẹ̀mi kannà nse ni, Ti o ba se àjèjì sí ọ, o dára bẹ́. Jẹ́ ki nse àlàyé fún ọ.  Kókó inú rẹ̀ ni pé Jesu sọ fún wa pé ó se pàtàkì lati ni ìrìbọmi ti Ẹ̀mi Mimọ́ ti o si sọ pé o kò gbọdọ́ kúrò nílé láìní ẹ̀mi yi! Èmi kọ́ ni o sọ bẹ́; Jesu se bẹ́ ninú Ìse Awọn Àpọsteli 1:4-5.

> *Kí wọn kí ó máse kúrò ní Jerúsálẹ́mù,sùgbọ́n kí wọn kí ó dúró de ìlérí Baba, èyítí ó wípé, ẹ̀yin ti gbọ́ ní ẹnu wọn. Nítorí nítòtó ni Jòhánù fi omi baptisi; sùgbọ́n a o <u>fi Ẹ̀mí Mímọ́ baptisi yín</u>  kì íse ọjọ́ púpò lati ònìí lọ*
>
> —Ìse Àwọn Apọsteli: 1:4b-5
>
> *Sùgbọmn ẹ̀yin ó gba agbára nígbà tí Ẹ̀mí Mímọ́* bá bà *le yín: ẹ ó ma se ẹlẹ́ri mi.*
>
> —Ìse Àwọn Apọsteli: 1:8

Sakiyèsí ohun ti Jesu sọ, “ma kúrò ni ilé laíni èyí—èyí se pàtàkí" pàtàkì julọ, ohun ti ó nsọ ni pé O nílò agbára yìí lati siṣẹ́ Ọlọrun, lati le jẹ́ ẹlẹ́rí ti ìjọba Rẹ̀. Síbẹ̀ lóde ònìí, Ọ̀pọ̀lọpọ̀ Kristiàni  ló wà ti wọn o tí gbọ́ nípa tàbi ni ìrírí ti ìrìbọmi ti Ẹ̀mi Mimọ́, Ọ̀pọ̀lọpọ̀ àwọn Kristiàni ti wọn dàgbà ninú ìjọ Ọlọrun ti wọn ó sì tún tí gbọ́ nipa ìwúlò ti ìrìbọmi ti Ẹ̀mi

Mimọ́. Tàbi pé wọn dàgbà ninú ìjọ ki wọn si ti sọ fún wọn wípe ìrìbọmi ki íse fún ònií; iṣẹ́ ìyanu nà ti kọjálọ.

Bi èmi náà ti se dàgbà lati inú ìjọ Ọlọrun nìyìí ti mi ò sì gbọ́ nipa Ìrìbọmi ti Ẹ̀mì Mimọ́. Mo ti gba ọ̀pọ̀lọ̀pọ̀ ìwe ìfiranṣẹ́ lati ọ̀dọ̀ àwọn ènìyàn kaàkiri lágbáyé ti wọn sẹ̀sẹ̀ ngbọ nipa òtítọ́ ti o lagbára yìí bakannà. Ọ̀pọ̀ àwọn ti o kọ̀we rànṣẹ́ ni wọn nbèrè ìbérè lorí ẹbún yìí pé báwo ni ìwúlò rẹ̀ si lode onìí, idi sìnìyìí ti mo se wa kọsilẹ̀ òtítọ́ nipa Ìrìbọmi ti Ẹ̀mi Mimọ.

Mo si gbàgbọ́ pe Bibeli sọ ni kedere nipa rẹ̀, mo si fẹ́ ki Bibeli tún sọ́ rọ́ fún ara rẹ̀. Ki o ba le dáhùn gbogbo ìbérè rẹ. Sugbọ́n, ni àkọ́kọ́, Mo fẹ́ se awọn àgbékalẹ̀ kan fún ọ tí yóò mu ki o le sàwárí àwọn òtítọ́ nipa ìríbọmi ti Ẹ̀mi Mimọ́.

Nigbati mo wà ni kékeré, ongbẹ Ọlọrun ngbẹ mi gan (bẹ́ na sìní, súgbọ́n mo ti dàgbà), mo si ma nlọ si ìjọ àpéjọpọ̀ àwujọ àwọn onigbàgbọ́. A ma nse ìsìn bi a tin se ni gbogbo ọjọ́ ìsinmi. Bóyá ìwọ na se bẹ́ pẹ̀lú. Mo rànti awọn orin kan ti à má nkọ ni ìdakẹ́jẹ́ ni àsikò ti a ban se àsàrò. À má nsábà ka àdúrà Oluwa, Oniwáàsù yóò si wàásù, à o si kọ orin ìparí àti ore-ọ̀fẹ́. Gbogbo ìsìn ni o ti ni àlàkalẹ̀ ni ọ̀nà kannà.

Awọn èniyàn wọnyìí fẹ́ràn Ọlọrun gàn, sibẹ̀ wọ́n jẹ́ ìyanu. Sugbọn mi o rí ohun ti o jẹ́ otítọ́ ti ìhìnrere ninú wọn, mi o rí kí ayé àwọn ènìyàn yípadà, mi o rí ki ara àwọn ènìyàn yánipa agbára Ọlọrun. Mo lerò pé mi o ba kúkú sọ pé mi o rí ifarahàn ti ìjọba Ọlọrun nibẹ̀.

Nìgbati mo wà bi ọmọ mejidinlógún, ongbẹ Ọlọrun ngbẹ́ mi gàn, mo si nba baba ta ọjà wọn ounjẹ bi ìpanu (písà). Ni àlẹ́ ọjọ́ kan ọ̀dọ̀mọkìnrin kan wá si ilìtajà wa ọ si pè mi si ibi ìsọjí kan. Ninú ile ìjọsin àgúdà kekere kan ni wọn ti seé ni ilú mi, oniwàásu ọjọ́ na ni ajinrerekan ti o sọ́rọ́ nipa Jesu pé o nse ohunkannà loni, bí ó ti se ni ọjọ́ Bibeli.

Bayìí, mo se afiyèsí ohun tí ó sọ, nitori mo fẹ́ ríi kí ó sẹlẹ̀ bẹ́. Awọn ọ̀rẹ́ mi kan si wà ti o jẹ́ ìjọ ti wọn nlọ ni, mo wa pinu lati lọ sí ìsọjì nà. Bíótìlẹ̀jẹ́pé, mi kò ti gbọ́ nipa ìrìbọmi ti Ẹ̀mi Mimọ ni alẹ́ ọjọ́ nà, mo ri ifọwọ́kàn ti ìwàláyè ti Ọlọrun ninú ìsìn nà. Àwọn ọ̀rẹ́ mi tin jọ́sin ninú ìjọ na rọ̀ mi lati pada wá ni ọjọ́ ìsinmi ti o nbọ̀, ti mo si lọ. Mo nifẹ́ si ìjọ na mo sì wá darapọ̀ mọ́ ìjọ nà.

Ọ̀ṣẹ̀ diẹ lẹ́yìn ìsọjí nà, mo ba àwọn ẹgbẹ́ obinrin ìjọ na pàdé ti wọn wa

se ìsìn ninú ijọ àti kọ́ ẹ̀kọ́ Bibeli ni ọ̀sẹ̀ ọ̀sẹ̀. Wọn nsọ̀rọ̀ nípa Ìrìbọmi ti Ẹ̀mi Mimọ́, àwọn ẹbùn Ẹ̀mi, àti ọ̀pọ̀ àwọn nkan miràn tíi mi o ti gbọ́ rí. O sí wù mi lati gbọ́ nípa agbára yìí ti wọ́n nsọ̀rọ̀ nipa rẹ̀, mo wa bèrè pé se mo le máa wá si ipàdé ẹ̀kọ́ Bibelì àwọn obinrin. Òwúrọ̀ ni wọn máa nse ẹ̀kọ́ Bibeli ti wọn ,niwọ̀n igbà ti o sí jẹ́ wipé alẹ́ ni ọjà titi tíwa, mo pinu ati má lọ si ìpadé nà

Nigbati mo dé ìpàdé nà, mo wa ri wipé èmi nikan ni ọdọ́mọkùnrin ti o wà láarin wọn. ti o si jẹ́ ọmọ ọdúnmejidinlógún, sugbọ́n kò se nkankan si mí. Mo nlọ fún ẹ̀kọ́ Bibeli nitori ongbẹ ọ̀rọ̀ Ọlọrun ti o ngbẹ mi Mo si bèrè ọ̀pọ̀lọpọ̀ àwọn ìbérè.

Àwọn obinrin nà ni sùúrù pẹ̀lú mi gan, wọn si kọ̀ mi ni Bibeli wọn tún fihàn mi ninú Bibeli *mi* pé ìrìbọmi ti Ẹ̀mi Mimọ́ wà fún òde oníí àti pé agbára Ọlọrun si wà si bẹ̀ loníí bi ìgbàti Jesu wà lorí ilẹ̀ ayé. Ibiti ò dára ju nibẹ̀ ni, nigbàti wọn sọ̀ wipe ó wà fún *gbogbo* awọn ti o ba ti gbàgbọ́—o wà fún gbogbo ẹnikẹ́ni ti o bá bèrè.

Lẹ́yìn ìgbàti mo ti nlọ sí ìpàdé ẹ̀kọ́ Bibeli wọn fún bi ọsẹ̀ diẹ, Wọn wa sọ fún mi pé àwọn obinrin àpapọ̀ ti wọn npè wọn ni Ẹgbẹ́ Àwọn Obinrin Tontàn yóò se ìpàdé gbogbo. Ẹgbẹ́ yí ti wà, wọ́n sì tún wà, wọ́n jẹ́ ẹgbẹ́ ti o nkọ́ni nipa ìrìbọmí ti Ẹ̀mi Mimọ̀. Àwọn ẹgbẹ́ obinrin wọ̀nyìí fẹ́ lati lọ, wọn sì sọ fún èmi nà lati tẹ̀lẹ́ wọn lọ. Ni ayé ìgbànà, gbogbo ìjọ elétò ni wọn máa kó ara wọn jọ papọ̀ lati gbọ́ ati jẹ̀gbádùn ètò ìrìbọmi nà, ki o tó di àsikò yìí, àwọn ìjọ ọmọ lẹ́yìn Kristi (Pẹ́ntikóstal) nikan ni ó máa sọ̀rọ̀ nipá rẹ̀. Nigbánà ni àwọn ènìyàn má npé àwọn ẹlẹsin ìgbàlódé, nibiti ẹ̀kọ́ nipa ti Ẹ̀mi Mimọ́ wagb a gbogbo ìjọ kan.

Nigbati mo lọ síbi ipade yìí, mo ri pé ọ̀pọ̀lọpọ̀ àwọn obinrin ni o wà nibẹ̀. Bákannà, mo wa larin àwọn ọkùrin ti kò tó nkan, sùgbọ́n ìwàálýè Ọlọrun kun inú ile nà.

Ó yàmilẹnu bi awọn ènìyàn ti sọ̀rọ̀ nipa bi wọn ti gba ìwosàn, mo si nwò wọn tìyanutìyanu bi awọn kan ti ngbàdúrà ti wọn si nsubú lulẹ̀. Nkan yi jẹ́ ohun ti mi o ti rírí, o jọmi lojú o si fẹ́ rúmilójú pẹ̀lú. Mo wá sèwadi pé àwọn ènìyàn na npé ni ẹniti a pa ninú Ẹ̀mi. Bì o ti lẹ̀jẹ́ wipé, o jẹ́ nkan àjeji ní tara si mi, sugbọn àwọn ti o ni ìrírí yìí dide bi ẹni ti ó ni ifọwọkàn Ọlọrun. Nigbati o yá, mo wa bèrè lọ́wọ́ obinrin kan pe se ẹran ara wa le gbá agbára ti Ọlọrun ti nkan si leni àgára lorí rẹ̀, ti à npè

ni ìfòróróyàn."

Wọ́n si fihàn mi, ibiti o ti sẹlẹ̀ ninú iṣẹ́ ìranṣẹ Jesu. Ninú ìwe Johanu 18:4b-6 nigbati àwọn ọmọ-ogun wá lati wa mú u, Jesu si bi wọ lérè,

> "*Tani ẹ̀yín ńwa?" Wọ́n sì da a lóhùn wípé Jésù ti Násáretì. Jésù sì wí fún wọn pé, Èmi nìyìí. . . Nígbàtí Jesu sọ pé "Èmi nìyíi, wọ́n bì sẹ́yìn <u>wọ́n si subú lulẹ̀.</u>*

Ní àkókò orín ìyìn, gbogbo àwọn arabinrin ti o wà ẹ̀gbẹ́ mi ni ìnú wọn dùn, mo si gbọ́ ti ọ̀pọ̀ awọn ti o wà ni ayíka mi ni wọ́n nfèdèfọ̀ lati yin Ọlọrun. Gbogbo àwọn ohun ti o nsẹlẹ̀ ti ó jẹ́ titun si mi, ti mo kàn wá nwò tìyàlẹnu ninú àwọn ìpàdé nà. Bí ó tilẹ̀jẹ́pé ọ̀pọ̀ nkan ni ó se àjèjì simi, mi o le ké ìwàláayè Ọlọrun kúrú ninú àwọn ètò na. Inú mi dún pé mo wá ni ìrírí ohun ti o njẹ̀ ìhìnrere ni tòótọ, agbára Ọlọrun si wà, ti ó nsiṣẹ́ lorí ilẹ̀ ayé bi ọjọ́ ti Bibelí.

Ni ọjọ́ na, oniwàásu bèrè pé ẹnikẹ́ni ti o ba fẹ́ lati gba ẹbùn Ẹ̀mi Mim' kí ó jáde wá síwájú fún àdúrà ni opin ìpàdé nà. Mo si jade ki arabinrin nà le gbàdúrà pẹ̀lú mi. Bi wọ́n ti ngbàdúrà, mo ri ara mi ti ó kín fún agbára bi ìmisí àgbara Ọlọrun ti kún ile nà. Bi mo ti yí sí wíwà Rẹ̀, Inu mi dún lati gbọ́ wipé mo ti bẹ̀rẹ̀ si nígbàdúrà ninú Ẹ̀mi, àti sọ àwọn èdè ti mi o mọ̀jádé. Mo sì nfèdèfọ̀ fún ìgbà diẹ ni alẹ́ ọjọ nà. Inú mi dùn gàn ni nipa ìrírí tí mó ni, mo fẹ́ sọ fún gbogbo ènìyàn ti mo bá salábápàdé ohun ti ó sẹlẹ̀ si mi! Sùgbọ́n nigbàti mo sọ fún àwọn ọ̀rẹ́ mi ni ni ilé ìjọsìn wa ìrírí ti mọ ni, inú wọn kò dùn nipa rẹ̀. Wọ́n ní ìfèdèfọ̀ jẹ́ ti esù,tàbi ohun àtijọ́. Wọn wá kìlọ̀ fún mi lati jinnà si àwọn oli-ólí wọ̀nyìí!

Ni ayé ìgbàni àwọn ìjọ kò fí àyè gba ẹbùn Ẹ̀mi, ẹ̀kọ́ ìsáájú si ni pé àwọn àpọsteli ne ìsẹ àmi àti ìsẹ́ ìyànu. Sugbọ́n ni bayìí o wá yé mi pé agbára Ọlọrun kò kọjá lọ rárá!

Sáájú kí ìpàde yìí tó wayé, ni wọn ti fi mù se olri àwọn ọ̀dọ̀ ninú ìjọ Mẹtọ́disi nà. Kòsí ohun kan ti mo sin se nà jú kikò àwọn ọ̀dọ̀ jọ fún ìpàde ni àlẹ̀ ọjọ ìsinmi ni ìwájú ilé ìjọsìn. A máa nse ère ìdárayá, ati jẹ nkan ìpanú àti se ẹ̀kọ Bibeli niwọ̀nba. Ọ̀dọ́ ni èmi nà, ó kàn jẹ́ wipé mo ni ìtara fún nkan ti Ọlọrun mo si fẹ́ lati se ìrànwọ́.

Àwa bi mẹ́ẹ̀dógún ni àwa ọmọde ti a wà ninúẹgbẹ́ nà, lẹ́yìn ìrírí ti mò

ti ni ninú ìpàde àwọn obinrin títàn yìí, ni mo ti fẹ́ lati sọ fún wọn nipa Ìrìbọmi ti Ẹ̀mi Mimọ́ ti èmi ti ni ìrírí rẹ̀. Mo sàkíyèsí bi èmi nà ni, ọ̀pọ̀ wọn ni kò ti gbọ́ nipa rẹ̀ ninú ìsin ọjọ́ ìsinmi pàápá jùlọ ninú ìjọ wọn.

Kin to tún sọ ohun tó sẹlẹ̀, mo lérò pe kin tún sọ nkan ti mo ni lérò nigbànà fún yin. Mi o gba àṣẹ lọ́dọ̀ Pasitọ kin to ba àwọn ọ̀dọ́ sọ̀rọ̀ (Mo wa sẹ́sẹ́ mọ̀ pé ó yẹ kin se bẹ́) Mi o tún sọ fún wọn pẹ̀lú gbogbo àwọn ìrírí mi bakannà. Kì íse pé mo fẹ̀ dìtẹ̀ mọ ìjọ o, ki ísì se pé mó fẹ́ súnmọ Pasitọ. inú mi kan da dún ni. Ni àsikò nà, mo ó tilẹ̀ mọ àriyànjiyàn ti o wà lórí àkolé yi gàn, mi o si lérò pé Pasitọ le lòdì si.

Alẹ́ ọjọ́ ìsinmi, lẹ́yìn ti mo ti gba Ìrìbọmi ti Ẹ̀mi Mimọ́, mo ti pinú lati sọ fún àwọn ọ̀dọ́ ohun ti o sẹlẹ̀ si mi, àti lati fi awọn ẹṣẹ Bibeli ti o tún sọ̀rọ̀ nipa rẹ̀ hàn wọn ninú ìwe Ìse Àwọn Àpọsteli. Àwa ni wajú ile ìjọsìn à kan jokò yípo lórí ilẹ nigbà ti mo npín ìrírími pẹ̀lú wọn ti mó si lọ ka àwọn ẹṣẹ Bibeli ti o salayé nipa rẹ̀ fún wọn.

Ni alẹ́ ọjọ́ yí gàn ni Pasitọ wa si ìpàdé o si jokò ni àpá àlááfià mi bi mo tin pin pẹ̀lú wọn. Mi o ròó pé Pásítọ̀ wa laarin wa. Bi Pasitọ̀ mi, mo rò pé wọn ti mọ ohungbogbo ti mo fẹ́ sọ nibẹ́ẹ̀.

Nitorinà, mo pin pẹ̀lú wọn nipa ipade nà ti mo lọ àti ohun gbogbo ti morí. Mi o sọ̀rọ̀ pípọ̀ nipa ìfèdèfọ̀. Dípò rẹ̀, mo fojú mi si Ìse Àwọn Àpọsteli 1:9 Nibiti o ti sọ pé à ò gba *agbára* nigbàti Ẹ̀mi Mimọ́ bà ba le wa ti a o si ma se ẹlẹ́rí Ọlọrun ní òpin ìpàde, mi o ti ẹ mọ̀ bi ma ti mú ẹ̀kọ́ na wà si ìdánudúrò, mo kan sọ fún àwọn ọmọ nà ni pé gbé ọwọ́ rẹ sókè ti o ba fẹ́ gba Ìrìbọmi ti Ẹ̀mi Mimọ́.

Tori mi o mọ nkan ti máa tún se mọ, mo nsọ pé , èmi o tí rí ibiti ẹnikan ti se iṣẹ ìranṣẹ gbigba ìrìbọmi ti Ẹ̀mi Mimọ́ rí, yatọ̀ si ibi ìpadé àwọn obinrin tí mo lọ. Mo si lérò pe mo mọ bi ẹṣẹ Bibeli mejì kan ti mo le fi tì lẹ́yìn ni igbà na. Mo wa sọ fún wọn pé gbe ọwọ́ rẹ sókè ti o ba fẹ́ gba ẹbùn Ìrìbọmi ti Ẹ̀mi Mimọ, ki ẹ tẹríba ki á gbàdúrà" ohun ti mo sọ nà nìyìí. mi o fọwọ́ kàn wọ́n tabi kọ́ wọn bi wọn ti se le gba Ẹ̀mi Mimọ́. A tẹríba, à sì ngbàdúrà. lótìtọ́ ni a di ojú wa lati gbadúrà bi àwọn Kristian yókù ti ma nse ti wọn kọ́ wa. “ó dára.”

Bi mo ti jóko lẹ̀yìn ti a se “Àmin,” mo béré si ni gbọ̀ gìdìgìdì láàrin àwọn ọmọde. Mo la ojú mi mo ri wipé àwọn kan ti nsunkún, àwọn kan ti ngbọ̀n, àwọn meje ninú wọn ti bẹ̀rẹ̀ sí ní fèdèfọ̀. Bi wọn ti bẹ̀rẹ̀ si fèdèfọ̀,

mo ri im-lẹ̀ ti o ntan lojú wọn, Wọn ntàn bi imọ́lẹ̀! Ó yà mi lẹnu.

Pásitọ mi tí kò sọ́ nkankan lati ìgbà ti o tí dé fọwọ́ tọ́mi ni kiakia pé jẹ́ kin ri ọ́, ó ni se mo le bá ọ sọ̀rọ̀ bayìí. A kọ́já si yàrá ti o kàn wá, o wò mi lójú ó ni "Èsù ni yií ò, o kò le se adarí àwọn ọ̀dọ̀ nibíyìí mọ́. A kò ni fi ayè gbàá."

Mo ròó pé "*Báwo ni wa se sọ pé ti Èsù ni? Mo ní wo àwọn ọmọde wọ̀nyìí! bí wọ́n titàn!* O le rí ìfòróróyàn náà lorí wọn. Bẹ́ẹ̀ ni, Èmi gàn kò ti mọ ohun ti ìfòróróyàn jẹ́ nigbànà. Mo sa ri pé wọn ndán, mi o sì fọwọ́ kàn wọn tàbi sọ fún wọn pé ẹ se bàyí. Ó jẹ́ ohun ti orunilójú àti mu ìrẹ́wẹ̀sì bá mi.

Nigbati Pásítọ̀ mi bámiwí bayìí, mi o sì mọ ohun tí má se. Ni ọjọ ìsinmi ti o tẹ̀le, mo padà lọ si ilé ìjọsìn, sugbọ́n mi o joko si ibiti mo má njoko sí tẹ́lẹ̀ ni ìwájú, mo lọ joko si ọwọ́ ẹ̀yìn. Mo mọ pé,arin èmi àtí Pásítọ̀ ko lọ gere mọ́ nitori ohun ti o sẹlẹ́ ninú ìpàde àwọn ọ̀dọ̀, mo si lerò pé o kin yẹra diẹ fún wọn fún ìgbà diẹ.

Ninú ìsìn òwúrọ̀ ọjọ́ nà ìdákẹ́jẹ́ àsikò síse àsàrò ọjọ́ na yàtọ̀. Àsìkò ti o lọ́wọ̀ gàn ni àsikò àdúrà ìdákẹ́jẹ́ ninú ìjọ. Gbogbo èniyàn ni o wà ni ìtẹríba, kòsí ohunkan ti o ndún ninú ìjọ. Ti àbẹ́rẹ́ ba bọ silẹ̀ yo dún. Ni àsikò yi gan ni ó dabi pé ẹnikan fọ́wọ́ tọ́mi léjìká. òpin ibi àga ìwàásù ni mo wà, o wa jẹ pé ẹnikan dúró ti o nfọwọ́ tọ́mi léjìká.

Àkọ́kọ́, àyàmi kọ́kọ́já lati rò pé ẹnikan yóò ma rìn ni iru akókò ti o ni ọ̀wọ̀ ti ohun gbogbo wà ni ìdákẹ́rọ́rọ́ ninú àdúrà. Nigbatí mo gbé oju sókè , o yàmi lẹnú lati rí ọkan lara àwọn ọmọde ti a jọ wà ninú ìpade ni ọsẹ to kọjá. Mo si mọ pé ọkan lára àwọn meje ti ó ti gba Ìrìbọmi Ẹ̀mi Mimọ ni alẹ́ ọjọ́ nà ni. Ó fọwọ́ tọ́mi ó ni "jẹ́ kí a lọ!" mo ròó, *jẹ́ kí a lọ?Lo si ibo?*

Sí ìyàlẹnu, nise ni o tún tàn bi alẹ́ ọjọ nà, o ti gbá ẹbùn Ẹ̀mi Mimọ̀, mo sì mọ̀ pé Ọlọrun nse nkan ninú ayé rẹ̀. Sùgbọ́n mi o mọ boyá àkókò niyìí latí se ohunkóhun niwọ̀n igbà ti wahala ti wà pẹ̀lú Pásítọ̀ ìjọ. Mo si mọ pe a kò le se ohunkohun ti a fẹ́ se mọ ni òwúrọ̀ ọjọ́ isinmi ninú ìjọ. Nigbànà ni o dahùn pé, "Mo fẹ̀ lọ́ gbadúrà fún mọ̀mọ́ mi."

Nibayìí, ó sẹ́sẹ́ wa nyé mi ohun ti nsẹlẹ̀. Mo— mọ̀—rẹ̀. Ìya sékélé, ti kò lára, ti ara rẹ̀ kò! sì dá, o tin se àìsàn lati igbà pípẹ́. Egungun ọpá ẹ̀yìn rẹ marun ni o ti bajẹ́, Ti àwọn Dọ́kítà ti ni ọ̀na àbayọ kan ti o ni ni ki wọ́n se iṣẹ abẹ fun lati le tòó padà, ọ̀rẹ́ mi si ni ọmọ rẹ̀ kansoso ti o ni. Bẹ́ẹ̀ni, ọ̀rọ̀

ìyá rẹ káalára.

Lẹ́yìn ti ó ti gba Ìrìbọmi ti Ẹ̀mi Mimọ̀, ó dáalojú pé Jesu le wo ìyá oun sàn. Nigbàti ó  sọ pé "Jẹ́kí à lọ" Mo lérò wipé yóò lọ sí ibiti ìyá rẹ̀ wà jẹ́jẹ́ ni lati lọ gbé ọ̀wọ́ lée lorí àti gbàdurà fún un. Sùgbọ́n kò se bẹ́ẹ̀. O tọ iya rẹ̀ lọ lorí pẹpẹ, ó si gbe wa si ìwajú ninú ìjọ.

Ó gbée joko ó si bẹ̀rẹ̀ si ni gbà àdúrà fún ni ìfèdèfọ̀ bi ohùn rẹ̀ ti lọ sókè tó. Ránti pé, gbogbo nkan yìí sẹlẹ̀ ni àkókò ti gbogbo ijọ èniyàn "dákẹ́jẹ́" fún síseàsàrò, ti ó wa di nkan ti wọn ti npariwo. Àyà mi já! Nigbànà, ni o wá kọjú sí mi pé" "ìwọ se àlàyé ohun ti o nsẹlẹ̀."

Mo wa níran ìdí ti o fí s; pẹ̀ kin ma bọ̀. Ó fihàn pé èmi ni o sọ fún un nipa Ìrìbọmi ti Ẹ̀mi Mimọ́, Ó nsọ pé mo le sọ fún gbogbo ìjọ nipa rẹ̀, nigbàti wọn ti ríi ti ó nfèdèfọ̀ gbàdurà fún ìya rẹ̀.

Mo wá duró ni iwáju ìjọ bi agbẹnusọ rẹ̀, nibiti ó ti ngbàdúrà fún ìyà rẹ̀ ninú ẹ̀mi. Mi o tilẹ̀ mọ ohun ti má sọ, niwọ̀n ìgbàti Pásítọ̀ Joko ti o nwò mi. Mo kan sọ fún gbogbo ìjọ pé o ti pẹ́ ti ara ìya rẹ̀ kó ti yá pé ó wá ngbàdúrà fún un lati inú Ẹ̀mi, èyítí ó sì wà ninú Bibeli. Sé o wá mọ ohun tí ó sẹlẹ́ ni owúrọ̀ ọjọ́ na ni ó gbà ìmularadá rẹ ninú ìjọ!

Ìgbàgbọ́ ọmọkan ti kò ka ohun ti ẹnikẹ́ni le rò nipa ki on má fèdèfọ̀ gbàdúrà. Ó mọ̀ dájú pé Ẹ̀mi Mimọ́ wà láayè, ó si le wo ìyá oun sàn.

Bí o ti lẹ̀ jẹ́pé lọgàn ni  a múu laradá, ìjọ kò faramọ, kòdà ọ̀pọ̀ ni awọn tówá ba mi pé "mi o ni o se gbàdúrà fún ìya rẹ̀, sùgbọ̀n  a kò le gbà ìfèdèfọ̀ yẹn." Mo mọ̀ dajú pé èsu kò fẹ́ràn fifièdèfọ̀ rárá, mo si setan lati ràn ọ́ lọ́ wọ́ idi ti o fi kórira ìfèdèfọ̀ ki a tó ka ìwe yí tan.

Bóya o dàgbà ninú ìjọ ti wọn kò ti fi kọ ara wọn ni ti ẹbùn Ẹ̀mi àti ìfèdèfọ̀.  Tàbi o dagbà ni ibiti wọ́n  t kọ́ wọn pé ayé ìfèdèfọ̀ ti kọjá ki ìse fún àkókò ti a wà yìí. Ìbérè yí kò le lati dáhùn. Bibeli fi yé wa kedere. Jẹ́ki a lo wo Ọ̀rọ̀ Ọlọrun ki a sì wádi òtítọ́ nipa Ìrìbọmi ti Ẹ̀mi Mimọ̀. Ẹ jẹ́ kí a padà lọ wo ẹsẹ Bibeli ti a kà ni ìbẹ̀rẹ̀ orí ìwé yìí.

*Kí wọn kí ó máse kúrò ní Jerúsálẹ́mù,sùgbọ́n kí wọn kí ó dúró de ìlérí Baba, èyítí ó wípé, ẹ̀yin ti gbọ́ ní ẹnu wọn. Nítorí nítòtó ni Jòhánù fi omi baptisi; sùgbọ́n a o fi Ẹ̀mí Mímọ́ baptisi yín  kì íse ọjọ́ púpò lati ònìí lọ*

—Ìse Àwọn Apọsteli: 1:4b-5

**"Ọ̀RỌ̀ TI ÈMI NSỌ FÚN YÍN, ÈMI KÒ DA A SỌ; SÙGBỌ́N BABA TÍ NGBÉ INÚ MÍ, ON NI NSE ÌSẸ̀ RẸ̀."**

**—JOHANU 14:10B**

Ọ̀pọ̀lọpọ̀ àwọn kókó ni a le rí ninú ẹsẹ Bibeli yìí:

1. Ìrìbọmi ti Ẹ̀mi Mimọ́ yàtọ̀ si síse ìtẹbọmi ninù omi.

2. Jesu sọ pé, o se pàtàki gàn ni. Kódà, Ó jẹ́ ki ó yé wa pé laísí Rẹ̀ a kò ni le se ohunkóhun.

Ránti Jesu sẹ́sẹ́ sọ fún àwọn ọmọ ẹ̀yìn Rẹ̀ ni pé ki wọn lọ máa wàásù ihìnrere ni gbogbo orilẹ́-èdè, sùgbọ́n wọn kò ni le se afihàn tàbi jẹ̀rí si Ìjọba Ọlọrun laisi ìrìbọmi. Nigbànà ó wá sọ pé, "Ẹ dúró titi ẹ ó fi gbà agbára."

> *Sùgbọmn ẹ̀yin ó gba agbára nígbà tí Ẹ̀mí Mímọ́* bá bà *le yín: ẹ ó ma se ẹlẹ́ri mi ni Jerúsálẹ́mù, ati ni gbogbo Jùdia ati ni Samária tití de òpin ayé*
>
> —Ìse Àwọn Apọsteli: 1:8

Agbára Èdè Giriki fún *agbára* ni à npé ni *dúnnámì* ninú gbolóhùn ọ̀rọ̀ yìí ni a ti ri ọ̀rọ̀ ti a npe nì dynàmite. A wá rí pé agbára Ọlọrun wá sórí wa fún wa lati le è sişẹ́ Rẹ́. Ni ìbẹ̀rẹ̀ iṣẹ́ ìránşẹ Jesu, Ó ti sọ pé agbára, tabi ìfòróróyàn, ohun fi nşişẹ́, wá lati ọ̀dọ̀ Baba.

"*Orọ̀ tí èmi nsọ fún yín , èmi kò da a sọ; sùgbọ́n Baba tí ó ńgbé inú mi, òn ni ó ńse isẹ́ rẹ̀"* (Johannu 14:10b)

"*Lóòtọ́ ni mo sọ fún yín, Ọmọ kò le se ohunkóhun fún ara rẹ̀.* (Johanu 5:19)

Sé o ríi, Jesu nílò ìrólágbára ti Ẹ̀mi Ọlọrun fún ara. Gbolóhùn ọ̀rọ̀ tí a npè ni *ìfòróróyàn* túmọ̀ si "lòó sí" Jesu gba ìfòróróyàn ni odò Jordani lati ọ̀dọ̀ Baba Rẹ̀ nigbàti Ẹ̀mi Mimọ́ bà lee lórí bi àdàbà.

Lẹ́yìn ìgbàti Jesu ti gba ìfòróróyàn yìí tán ni o tó le bẹ̀rẹ̀ sí ní se iṣẹ́

ìránṣẹ́ ti ìjọba. Tí *Jesu* ba fi nílò rẹ̀, àwa nà niló rẹ̀ pẹ̀lú! Agbára yìí ni yóò jẹ́ri (tabi se ẹlẹrí) nipaṣẹ̀ fifihàn pé òtítọ̀ ni Ọlọrun wà fún àwọn tí kò mọ̀ ọ́n.

Bibeli nà tún sọ wipé ẹ̀yìn yóò gba agbára nigbàti Ẹ̀mi Mimọ́ **BÁ BÀ LE YÍN**, kì íse nigbàti ó bá wọ inú rẹ bi o ti se ndi àtúnbi.

Ọ̀pọ̀ ni o rú lójú nigbàtí a bá nsọ̀rọ̀ nipa Ìrìbọmi ti Ẹ̀mi Mimọ́, wọn yóò ma ròó pé sbi àwọn ti gba Ẹ̀mi Mimọ́ bi awọn ti se ti gba Kristi tú awọn si tí di àtúnbi. Otitọ́ si ni pé wọn *ti* gba Ẹ̀mi Mimọ́ nigbàti wọ́n ti gbà Kristi. Ẹ̀mi Mimọ́ ti sọ ẹ̀mi wọn jí si Ọlọrun àti wà ni ọkansoso pẹ̀lú Ọlọrun.

A wà láyè sí Ọlọrun nipá agbára ti Ẹ̀mi Mimọ́ tí o wà ninú wa nigbàtí a ti di àtúnbí. Sùgbọ́n kíyèsí ẹṣẹ ìwe mimọ́ yìí pé nigbàti Ẹ̀mi Mimọ́ bá bà le yín. Èyí jẹ́ òótọ́ ti o se pàtàkì tí a o si tún gbé yẹ̀wò.

Ninú ìwe yíí: Bi o ti se di àtúnbi àti gba àmi ìfòróróyàn tàbi gbà ìtẹbọmí ti Ẹ̀mi Mimọ́ jẹ́ ìsẹ̀lẹ̀ mejì ti ó yàtọ̀ si ara wọn. Tí a ba lọ wo ìwe Johannu 20:21-22, yóò jẹ́ kí o yé wa sí dáadáa.

> *Jesu sì tún wí fún wọn pé, "Àlááfià fún yín gẹ́gé bí Baba ti rán mi, bẹ́ni èmi rán yín" Nígbàtí ó sì ti wí èyi tán, ó mí sì wọn, ó sì wí fún wọn pé. "Ẹ gba Ẹ́mí Mímọ́"*

A rí Jesu nibiyí lẹ́yìn tí ó tí jinde bi Ó ti kí àwọn ọmọ-ẹ̀yìn ati mi emi sí wọn àti sọ fún wọn ki wọ́n gbà Ẹ̀mi Mimọ́. Ni àsikò nà ni wọn di àtúnbi ti ẹ̀mi wọn si wà láyè si Ọlọrun lati ninú wá. Sibẹ̀ Jesu tún sọ fún wọn lati dúró fún ìrìbọmi ti Ẹ̀mi Mimọ́, ti yóò wa sọrí wọn.

Ti o ba jẹ́ wípé gbogbo Ẹ̀mi Mimọ́ ni wọn ti gbà nigbàti Jesu mi èmí si wọn ni, Kilódé ti Ó tún fi sọ fún wọn lati dúró ni Jerusalẹmu títí wọn o fi gba Ẹ̀mi Mimọ́ ti ó ti sèlérí pé yóò wá sórí wọn? Lẹ́ẹ̀kansi, àwọn ìsẹ̀lẹ̀ mejì ti ó yàtọ ti wọn sì nse ìṣẹ́ ọ̀tọ̀tọ̀, sùgbọ́n Ẹ̀mi kanna. Bakannà , bi mo ti sọ, Mo fẹ́ ki a mọ̀ pé a se ìrìbọmi ti Ẹ̀mi Mimọ́ fún Jesu ki o tó le bẹ̀rẹ̀ iṣẹ ìránṣẹ rẹ̀ ati múnà ninu rẹ̀ bo ti yẹ. Kí Jesu tó se ìrìbọmí ti Ẹ̀mi Mimọ́ kò si akọ́silẹ̀ ìṣẹ́ ìyanu kan ti ó ti se. Se Jesu sọ àkàrà di pupọ̀ nibi àsè ounjẹ àlẹ́ nigbà ti o sẹ̀sẹ̀ ndàgbà? Se ọ se iṣẹ́ ìyanu nigbati ó wà ni ọmọde? Se o sọ ounjẹ́ ara rẹ̀ di pupọ̀ nigbàti ounjẹ rẹ̀ ntán lọ nitori ebi npá? Rárá, kò se bẹ́ẹ̀. Kilodé tí kò fí sé? Ìdàhùn rẹ rọrùn kò sì le: *Kò le sé*.

Kò le sé, tití ó fi di *ẹ̀yìn* ìgbàti o gbàa Ẹ̀mi Mimọ́ ní odò Jọrdani ti ó wá bẹ̀rẹ̀ ìṣẹ́ ìyanu i se.  Se o wa ríi pé Jesu wá bi èniyàn.Kò wá bi Ọmọ Ọlọrun ninú agbára Rẹ̀ àti ògo. Bi ènìyàn, Bi ènìyàn ti wà bẹ́ẹ̀ on na pẹ̀lú wà. Kò le wòsàn tàbi se ìṣẹ́ ìyanu kankan, bi iwọ àti èmi kò ti le se ìṣẹ́ ìyanu kankan ni ti ara wa.

Bakanna, Kì íse bi àwa, ẹ̀mi Jesu kò kú sí ti Ọlọrun nigbàti à ṣẹ̀ṣẹ̀ bíi bi ọmọ ọwọ́. Gbogbo ìgbà ni ẹ̀mi rẹ̀ wà láyè sí Ọlọrun; Kótún nilò lati di àtúnbi bí àwa ti se. Sibẹ̀, bi ó tì lẹ̀ jẹ́ wípé ìyè Rẹ̀ wà láyè si Ọlọrun bi Ọmọ, Ó sì nilò lati gbà ìrìbọmi ti Ẹ̀mi MImọ́ kí ó tó le bẹ̀rẹ̀ iṣẹ́ ìránṣẹ́ Rẹ̀ bi àwa nà ti se.

> *Nígbàti a si baptisi Jesu tán, ó jáde lẹ́sẹ̀kannà lati inú omi wá; sì wò ó, ọ̀run sí sílẹ̀ fun un, ó sì rí Ẹ̀mí Ọlọrun sọ̀kalẹ̀ bí àdàbà ó si bà lee. Sì kíyèsi i ohùn kan lati ọ̀run wa, o wípe "Èyí niàyànfẹ́ ọmọ mi, ẹnití inú mi dùn sí gidigidi.*
>
> —Mattiu 3:16-17

Ranti, a má ronú Jesu bi Ọba àwọn ọba àti Oluwa àwọn oluwa, sùgbọ̀n íse lati inú ipò yìí ni o tin se ìṣẹ́ ìránṣẹ́ Rẹ̀, Ni ẹ̀yìn ti Ẹ̀mi Mimọ́ ti bá le ninú odò Jordani ni o tó bẹ̀rẹ̀ sí se iṣẹ́ àmi àti iṣẹ́ ìyanu.

Iṣẹ́ ìranṣẹ́ rẹ(nitori gbogbo onigbàgbọ́ ni a pè lati se iṣẹ́ Jesu) kò le bẹ̀rẹ̀ àyàfi tí o bá ti gba baptisi pẹ̀lú Ẹ̀mi Mimọ́—nilò agbára ti Ẹ̀mi MImọ̀ lati le mú ki o séése. O si nílò agbára lati le gbà adurà ninú Ẹ̀mi lati le mọ̀ bi wa ti se wọ́n, ti a  jiroro lorí wọn ti ó ba yá.

Lóòtọ́, o le  lo ìrírí ẹniti  ó ti di àtúnbi lati sọ fún awọn ẹlomiràn ohun ti Bieli sọ nipa ìgbàla. Ọ̀pọ̀lọpọ̀ àwọn Kristiani ti wọn ò ti  gbà ìrìbọmi ti Ẹ̀mi Mimọ́ ni wọ́n si múnà ninú pínpín Ìròyìn ayọ̀ ti ìhìnrere, sugbọ́n wọn kò ni agbára lati se àfihàn ti ìjọba Ọlọrun bi Jesu ti se. Èyí si nfa ọ̀pọ̀ ìrẹ̀wẹ̀sì ninú wiwàásu  ìhìnrere.

Nigbati Jesu Kojú àwọn Farisi nipa àinígbàgbọ́, Ó ntọkasí àwọn iṣẹ́ ìyanu gbogb tí ó ti se. Ó ni,

"*Ẹ gbà mí gbo pe, èmi wà nínú Baba, Baba sì wà ninu mi;* <u>*bíkòse bẹ́ẹ̀*</u> *ẹ̀gbà mí gbọ nítorí àwọn isẹ́ nà pàápàá ọ*" (Johanu 14:11).

Jesu mọ̀ ọ́n mọ̀ sọ ọ́ ní pàtàkì pé ìfihàn ti ìjọba Ọlọrun yìí ni fi òpin si gbogbo aríyànjiyàn; àwọn wàhálà nà sì ti kalẹ̀. Nibayìí, lótítọ́, gbogbo onigbàgbọ́ ni ó ni ẹtọ́ labẹ́ òfin fún ohungbogbo ti Jesu ti san ìdíyelé fún, pẹ̀lú ìwòsàn. Gbogbo nigbàgbọ́ ni o le gbà gbogbo ìlérí Ọlọrun nipà ìgbàgbọ́( àdéhùn pẹ̀lú ọ̀run), wọn kò si nilò ìrìbọmi ti Ẹ̀mi Mimọ́ lati gbàá lati ọ̀dọ̀ Ọlọrun.

Sùgbọ́n fún agbára rẹ lati máa sàn lati ara rẹ sí ọ̀dọ̀ ẹlomiràn, àti fún ìwọ gàn lati ma sàn ninú àwọn ẹbùn ti Ẹ̀mi àti lati ma jẹ́ ìgbàdùn àwọn ànfani ti rinrìn ninú àwọn ohun ìjinlẹ̀ ti àwọn ọ̀run nipaṣẹ̀ gbigbàdúrà ninú Ẹ̀mi ti ns ìfèdèfọ̀, o gbọdọ̀ ni agbára ti ìfòróróyàn! ó le ma yé ọ́, ohun ti mò nsọ nigbàti mo ní ìfèdèfọ̀ gbàdúrà. Ma jẹ́ kí ó bà ọ́ lérù; ma se àlàyé lẹkúnrẹ́rẹ́ ti bá yá.

Ọmọmi obinrin Amy ni ó darí orin ìjọ́sìn ninu ìjọ wa, Faith Life Ẹhurẹh, ni Albany Titun, Ohio. Fun bi ọ̀dun diẹ, ó wa ni ipò kan ti o máa nrú gbogbo wa loju—ikùn rẹ̀ ó nrọra ndagbà diẹ diẹ o si nyọ síta. Bi ó tilẹ̀ jẹ́ wipé ọ̀dọ̀ ọ̀pọ̀ àwọn Dọkita( Onimọ̀ Ìsegùn Oyinbo) ni a ti dé, kò si ọkan ninú wọn ti ó rí ohun tí ó nse. Gbogbo wọ́n ni àbùdá rẹ̀ ni.

Ó dáa, nkan yì wà nibẹ̀ titi o fí dabi ẹniti ó ni oyún osù mẹfá. Ni àsikò yìí gàn, ni Amy lọ se àyẹ̀wò inú X-ray wàyìí o ó wá hàn kedere pé nkan kan ni o ndàgbá ninú ikùn rẹ. Nigbàtí a ti ríi bayìí Amy ti nròó pé ìgbesẹ̀ wo ni àwọn Dọkita yóò fẹ́ lati gbé, Amy si ti mọ̀ pé ti wọn ba ti se ìṣẹ́ abẹ fún un o le se ìdíwọ́ ati ri ọmọ bi fún oun ti un ba dé ilé ọkọ ni ọjọ́ iwaju. Ki ise ohun ti Amy fẹ́ lati se. Ó ti nwo bi oun ti di ìyà ọmọ. Ari pé nkan ti ó ndàgbà ninú ikùn rẹ́ yìí ti sákóba fún awọn ẹyá ara rẹ́ kan, ti o si nfá wàhálà fún Amy lati mú ki ounjẹ́ le tètè dá ninú rẹ́ àti ìsòro fún kindinrín rẹ́ nà. Ó wa pinnu lati fi ara rẹ fún ọ̀rọ̀ Ọlọrun ati fi àyè silẹ̀ lati fiyèsi ohun ti Bibeli kọ wa lorí ìwòsan. Ninú ọsẹ̀ yi kannà, Mo nse ìdanilẹ́kọ́ lorí ìwòsàn ninú ìjọ Faith Life Church. Lópin àwọn ẹ̀kọ́ yìí Amy sọ fún àwọn alágbà lati gbé ọwọ́ lé un ki wọn si gbadúrà lori àilera oun gẹ́gẹ́ bi ìwe Jakọbu ti sọ, ti wọn si se
bẹ́ẹ̀ fún.

> *Ẹnikẹ́ni ńse àìsàn nínu yín bí? Kí o pe àwọn àgbà ìjọ, kí wọ́n sì gbàdúrà sórí rẹ̀, kí wọn fi òróró kun un ni oruko Oluwa. Àdúrà ìgbàgbọ́ yóò si gba aláìsàn na là, Oluwa yóò si gbe dìde; bí o bá sì se pé o ti dẹ́sẹ̀ a o dárijin.*
>
> —Jákọ́bù 5:14-15


Amy ni ìdanilójú ninú Ọ̀rọ̀ Ọlọrun, *ó gbà á* ìwosan rẹ́ nigbàti wọ́n gbe ọwọ́ le e. Bí o tilẹ̀jẹ́pé, kò si ìfihàn kankan ti ara nipa ìmúláradá rẹ̀ ni àkókò náà a gbàdúrà fún, ó sì ni ìdánilójú pé àrà oun ti yá.

Lẹ́yìn òsẹ̀ meji, ó lọ sórí ìbùsùn rẹ, kò si tí sí nkankan ti ó farahàn ni àgọ́ ara rẹ̀ pé ara rẹ̀ ti yá, sugbọ́n nigbàti o jí ni òwúrọ̀ ọjọ̀ keji sí ìyàlẹ́nu, Ó ti dín kù ni ìwọ̀n pọùn mẹ́tàlà àti injisì mẹsan (ẹ́é pọun àti ó injísì) lati ẹ̀gbẹ́ rẹ ki ilẹ̀ tómọ́ òun nà pẹ̀lú sì sùn lọ. Ẹ̀yin rẹ́ ti o ti bà ti ọ dà bi pé wọ́n ta ni kòkò ti nàró padà si pò bó ti yẹ. Lẹ́ṣẹ̀kẹ̣ṣẹ̀ ni o ti gbà ìwosàn rẹ̀!



SÁÁJÚ KÍ Ó TÓ LẸ̀HÌN TÍ Ó TI

Àwọn àwòrán yìí nfi ìyàlẹ́nu agbára ìwòsàn hàn. Àwòrán ti o wà ni apá àlááfià ni bi Amy ti se rí tẹ́lẹ̀ nigbàti o lọ sùn sórí ìbùsùn rẹ̀. Àwòran ti ọwọ́ ọtún ni bí o ti se rí nigbati o jí.




O le rí X-ray ti ẹ̀yìn rẹ̀ ni apá àláàfià ki o tó gba ìwòsàn rẹ̀ ati X-ray tí ó yà ni ọ̀sẹ̀ kan lẹ́yìn ti ó ti gba ìwọ́sàn rẹ́ ni ti apá ọ̀tún. O le sakiyèsí àyipadà nla ni ibi ọ̀pá ẹ̀hìn rẹ̀!

Amy ni àkókò yìí òun na sì ni ọgá akọrin ti ó nsíwájú orin ìjọsin wa ninú ìjọ wa Faith Life Church. O le fojúinú wo nkan ti yóò sẹlẹ̀ ni ọjọ ìsinmi ti ó tẹ̀le nigbàti o dé ile ìjọsìn—gbogbo àwọn èniyàn nwòó! Awọn ènìyàn ndúro ni àrin ọ̀dẹ̀dẹ̀, ni ìyanu, wọn bèrè pé kinní ó sẹlẹ̀ si ọ́? Se o ti gba àgọ́ ara miràn ni? Gbogbo ìjọ ni o nyàlẹ́nu ni ọjọ́ isinmi nà bi wọn ti rí Amy niwáju ìjọ ti ó nkọrìn ìjọsin, ìfihàn agbára ti ìjọba Ọlọrun yìí mu ọ̀pọ̀lọpọ̀ èniyàn tọ Ọlọrun wà ọ̀pọ̀ ni ó si gba ìwòsàn ti wọn na ni ọjọ́ nà.

Ó ni lati gbà pẹ̀lú mi, pé àwọn èniyàn nilò lati ri iṣẹ́ agbára ti ìjọba Ọlọrun. Ninu Ìse Àwọn Àpọsteli 1:8, a le rí bi ìfòróróyàn, àti ìrìbọmi ti Ẹ̀mi Mimọ́ yí ti se pàtàkì.

> *Sùgbọmn ẹ̀yin ó gba agbára nígbà tí Ẹ̀mí Mímọ̀* bá bà *le yín: ẹ ó ma se ẹlẹ́ri mi ni Jerúsálẹ́mù, ati ni gbogbo Jùdia ati ni Samária tití de òpin ayé*
>
> —Ìse Àwọn Apọsteli: 1:8

Bi Jesu ti se rí ni wípé, ó se *pàtàkì* lati se ìfihàn ti Ìjọba ti Ọlọrún.

> *Àmì wọ̀nyìí ni yóò ma bá àwọn ti ó gbàgbọ́ lọ; Ni orukọ mi ni wọn o ma le àwọn èmí èsù jáde, wọn ó sì ma fi èdè titun sọ̀rọ̀; wọn o sì ma gbé ejò lọ́wọ́; bí wọn bá sì mu ohunkóhun tí o ni oró, kì yóò pa wọ́n lára rara; wọn o gbe ọwọ́ le àwọn ọlọ́kùnrùn ara wọn o da*dá.
>
> —Máákù 16:17-18

Gbe ejò lọ́wọ́ àti mimu ohun olóró ntọ́kasí ìjọba ti Satani ti o si nsọ́ ni ti ẹ̀rù. Ati sẹ́gun ìjọba ti Satani. Jesu kò sọ fún wa nibiyí lati gbé ejò tàbi mu ohun olóró, bikòsepé Ó nlo gbolóhùn ọ̀rọ̀ na bi apẹẹrẹ ti agbára ti a ti fifún wa lorí ọ̀tá. Ani lati lo agbára àti àṣẹ ti Ọlọrun lorí ijọba ti Satani ki a sì sọ àwọn ènìyàn di òminira!

Sakiyèsi pé Jesu sọ wipé ***"àmì wọ̀nyìí"*** yóò ma bá àwọn tí ó gbàgbọ́. Bi awọn ènìyàn ba ti rí àwọn àmì (ìfihàn) ti ìjọba Ọlọrun, wọn o si bèrè pé bawo ni ó ti se sẹlẹ̀. Àmì ntọkasí ohunkan. Ni tirẹ̀, kì íse ìdáhùn ni, sùgbọ́ n ó ntọ́kasí Jesu, ẹnití nse!

Àmì wọ̀nyìí ni o fi òpin si gbogbo àriyànjiyàn nípa boyá tàbí pé Jseu ni Oluwa—ÒUN NJẸ́! Nigbàti àwọn ènìyàn si ri pé Óun ni, wọn ronúpìwàdà wọ́n sì wà si ọ̀dọ̀ Ọlọrun. Idi si nìyìí ti ìwọ ati èmi fi nilò Ìrìbọmi ti Ẹ̀mi MImọ́, a kò si le jafáfá/ múnádóko laisí rẹ̀!

Nitorina, nisisiyìí tí a ti se ifilọ́lẹ̀ iṣẹ́ dìẹ nipa idí tí o fi nilò Ìrìbọmi ti Ẹ̀mi Mimọ́, ẹ jẹ́ kí à lọ se àyẹ̀wò ninú Ìwe Mimọ́ Bibelí ti ó tọ́kasí ìfòróróyàn yìí.

ORÍ KAÀRÚN

# ÌJẸ́RÍ SÍ TI BÍBÉLÌ

Ọ̀kan lára ọ̀nà tí ó le mú kí ènìyàn ni òye ti Ìrìbọmi ti Ẹ̀mi Mímọ́ dáadáa ni kí ó tèlé àwọn ti o gbàá ni ọjọ́ Pẹntikọstì bi wọn ti se àkọsílẹ̀ rẹ̀ ninú Ìwe Ìse Àwọn Àpọsteli. Bi a ti ngbé ìwé Mímọ́ yẹ̀wò, ìgbàgbọ́ àti ìgboyà rẹ yóò tún dàgbà si pé ìrìbọmi yìí yẹ fún èmi nà'

*Nígbàti ọjọ́ Pẹntíkọ́sì sì dé,gbogbo wọn fi ọkàn kan wà níibìkan. Lójijì ìró sì ti ọ̀run wá, gẹ́gẹ́ bi ìró ẹ̀fufu líle, ó sìkún gbogbo ilé nibiti wọ́n gbé jóòkó. "Ẹ̀là ahọ́n bi iná sì yọ sí wọn ó pín ara rẹ̀ ó sì bà lé olúkulùkù wọn Gbogbo wọn sì kún fún Ẹ̀mí Mímọ́, wọn sì bẹ̀rẹ̀ si ni fi èdè míràn sọ̀rọ̀ bí emí ti fún wọn lóhùn.*

*Àwọn Ju olufọkànsìn láti orilẹ̀-èdè gbogbo lábẹ́ ọ̀run si ńgbé Jerúsálẹ́mù. Nígbàti wọn sì gbọ́ ìró yìí, ọ̀pọ̀lọpọ̀ ènìyàn péjọ wọn si dàmú, ńitori olúkúlùkù gbọ́ wọ́n sọ̀rọ̀ ní èdè rẹ̀.*

*Háà si se gbogbo wọn, wọ́n wí fún ara wọn pé, "wò ó, ara Gálílì kí àwọn ti ńsọ̀rọ̀ wọ̀nyíì nse? Èha sì ti se tí àwa fi ńgbọ́ olúkulúkù ní èdè wa nínú èyítí a bí wa? Àwọn ara Partia ati Media, ati Elamu, ati àwọn ti ńgbé Mesopotamia, Judea ati Kappadokia, Pọntu ati Asia, Frigia,ati Pamfilia,Ejibiti ati Ẹ̀kùn Libia, níhà Kirene, ati àwọn atipo Romu àwọn Ju ati aláwọ̀se Ju. Àwọn ara Krete ati Arabia—Àwa gbọ́ wọn ńsọ̀ro isẹ́ ìyanu ńlá Ọlorun ni èdè wa!"*

> *Ha si se gbogbo wọn, ó si ru wọn lójú, wọn wí fún ara wọn pe, Kíli a le mọ èyí si? sùgbọ́n awọn elòmíràn nsẹfẹ̀ wọn wipe, Awọn ọkunrin wọ̀nyìí kún fún waini titun.*
>
> —Ìse Àwọn Àpọsteli 2:1-13

Nkan àkọ́kọ́ ti mo fẹ́ ki o kọ́kọ́ rí ni pé Bibeli sọ pé ***gbogbo wọn*** si kún fún Ẹ̀mi Mimọ́ Èkejì, *gbogbo* wọn si nfèdèfọ̀. Boyá o ti gbọ́ ti àwọn èniyàn nse àpèjúwe ọjọ́ Pẹntikọsti ati sàlàyé idi ti gbogbo wọn se nfèdèfọ̀. Awọn kan sọ pé ìrírí ẹ̀ẹ̀kan nà ni ti o wáyé ni fún ìjọ, nitorí ti àwọn èniyàn kóra wọn jọ papọ̀ lati onirúrú orilẹ̀ èdè, pé ósì sé e sé ki wọn nilò lati wáasú ìhìnrere fún gbogbo ènìyàn ni oniruru èdè na.

Sùgbọ́n ti o bá wo ìwe Mimọ́, wa ri ibiti o ti sọ pé awọn ọgọ́fa ti o wà ni yára òkè wọn nsọ̀rọ̀ ìṣẹ́ ìyanu Ọlọrun. Wọn kò wáasù ìhìnrere: wọn kàn nyin Ọlọrun ni.

> *"Àwa gbọ́ wọn ńsọ̀ro isẹ́ ìyanu ńlá Ọlorun ni èdè wa" Ha si se gbogbo wọn, ó si ru wọn lójú, wọn wí fún ara wọn pe, "Kíli a le mọ èyi?"*
>
> —Ìse Àwọn Àpọsteli 2:11b-12.

Awọn ènìyàn ti ó dúró layíká ngbọ́ wọn tí wọ́n nyin Ọlọrun lógo ni èdè àbínibí wọn, ni hà se ati jọ wọ́n lojú. Nigbànà ni Peteru si dìde lati wàásù ìṣẹ́ ìránṣẹ́ ti ìgbàlà, àwọn ẹgbẹ̀rún mẹta ènìyàn ni ó si kún àwọn ìjọ ni ọjọ́ nà. Nísisiyìí, ti o ba jẹ́ pé àwọn ọmọ ẹ̀hìn ti *ńwàásù* ni fífèdèfọ̀, Peteru kò ni dìde lati má wàású. Sùgbọ́n titi, Peteru fi dìde ti ó nwàásù wọn kò ti mọ ìtumọ̀ ohun ti wọn ngbọ́. Wọn kì i lo ìfèdèfọ̀ lati wáasù ìhìnrere nigbànà, wọn kò sì lòó lati wáasù nisisiyìí pẹ̀lú. A ò si wo ànfàni ti ìfèdèfọ̀fún àwọn onigbàgbọ́ ninú ori ìwe yìí ti ó kàn, sùgbọ́n ni bayìí, mo kàn nsọ̀rọ̀ lórí ariyànjiyàn ti o wọ́pọ̀ ti mo ti gbọ́.

Lẹ́ẹ̀kansi, Mo tún fẹ̀ sọ̀rọ̀ lorí ohun ti Bibeli sọ́ pé gbogbo wọn si gbàá *gbogbo* wọn si nfèdèfọ̀. Bi Bibeli bá dáa dúró níbẹ̀, à bá máa se ìyèmejì lorí pé ìfèdèfọ̀ wà fún gbogbo ìjọ ni. Sùgbọ́n Bibeli kò se bẹ́ẹ̀. Dipò bẹ́ẹ̀ a rí pé ó sì ntẹ̀síwáju ati sẹlẹ̀ si *gbogbo ènìyàn kọ̀kan* ti ó ba ti gbàá ìrìbọmi

ti Ẹ̀mi Mimọ́ lẹ́yìn ọjọ Pẹntikọsti.

Jẹ́ ki nsọ fún ọ nipa arakùnrin kan tí ó wà nibẹ̀ ni Ọjọ́ Pẹntikọsti—tí orukọ rẹ̀ njẹ́ Filippi.

> *Àwọn tí wọ́n sì túká lọ sí ibi gbogbo, wọ́n ńwàásù ọ̀rọ̀ na. Fílípì sí sọ̀kalẹ̀ lọ sí ìlú Samárià, ó ńwàásù Kristi fún wọn, Àwọn ìjọ ènìyàn si fi ọkàn kan fiyèsí ohun tí Fílípì ńsọ, nígbàti wọ́n gbọ́ ti wọ́n sì nri isẹ́ àmì tí ó nse.*
>
> —Ìse Àwọn Àpọsteli 8:4-6

Nibiyìí a ri Filippi ti ó nsafihàn Ìjọba Ọlọrun fún àwọn ènìyàn ti o ngbọ́ ọ. Bi o ti se yẹ kí ó rí lóde onìí niyìí; Nigbàti àwọn ènìyàn ri iṣẹ́ àmi, nigbàti wọn rí *èrí* tì ìjọba Ọlọrun, wọn o fiyèsi àti gbọ́ ohun ti o bá nsọ

> *Ọ̀pọ̀ nínú awọn tí ó ní ẹ̀mí àìmọ́ ti ńkígbe lóhùn rara, jáde wá àti ọ̀pọ̀ àwọn tí ó ni àrùn ẹ̀gbà àti àwọn amokún a si se dídá ara wọn Ayo púpọ̀ sì wà ní ilú.*
>
> —Ise Àwọn Àpọsteli 8:7-8

Kíyèsi pé Filippi nrìn ninú agbára ti ó sẹ̀sẹ̀ gbà nigbàti ó wà ni Jerusalẹmu. Iṣẹ́ àmi sì ntẹ̀le, gẹ́gẹ́ bi agbára Ọlọrun ti jẹ́ ẹ̀rí sí gbogbo rẹ̀. Ó ti gba *dunamisi* (tí à npé ni agbára ni èdè Giriki); ó wa mú kí ó di ẹlẹ́rí ti ìjọba Ọlọrun.

> *Nígbatí àwọn apọ́steli ti ó wà ní Jerúsálẹ́mù si gbọ pé àwọn ara Samarià ti gba ọ̀rọ̀ Ọlọrun wọ́n rán Péterù òn Jòhánù si wọ́n. Nígbàtí wọ́n si sọ̀kalè, ki wọn ki o le ri Ẹ̀mí Mimo gba, nitorí títi o fi di igbana kò ti bà lé ẹnikẹ́ni ninu wọn, kikia baptisi wọn ni oruko Jesu Oluwa Nígbànà ni wọ́n gbe ọwọ́ lé wọn , wọ́n si gba Ẹ̀mí Mímọ́*
>
> —Ise Àwọn Àpọsteli 8:14-17

Nígbàti àwọn apọsteli ti ó wà ni Jerusalẹmu si gbọ́ pé àwọn àrà

Samarià ti gba ọ̀rọ̀ Ọlọrun wọn rán Peteru on Johannu si wọn. Nigbàti wọn sọkalẹ́, kí wọn ki ó le rí Ẹ̀mi Mimọ́ gbà, nitorí títí ó fi di ìgbànà kò tì bà lé ẹnikẹ́ni ninú wọn. Sibẹ̀ Bibeli sọ pé àwọn ẹ̀mi àìmọ́ fi wọn silẹ̀, àwọn ènìyàn si gbà ìwòsàn wọn, iṣẹ́ agbára Ọlọrun sì sẹlẹ̀ nibẹ̀, àwọn ènìyàn si gbàgbọ́ ninú Jesu wọn si baptisi wọn ninú omi. Sùgbọ́n ó ni Ẹ̀mi Mimọ́ KÒ TÍ BÀ LÉ ẹnikẹ́ni ninú wọn!

Se o ri pé, Filippi wàásù ìgbàlà gbogbo wọn sí gba àti gbà á. sùgbọ́n wọn kò ti gba Ìrìbọmi tí Ẹ̀mi Mimọ́ sibẹ̀. Wọn ti di àtúnbi, Súgbọn wòó bi à ti kọ́ọ́: Ẹ̀mi Mimọ́ "KÒ TÍ BÀ LÉ ẸNIKẸ́NI NÍNÚ WỌN." ìyatọ yí wà nibẹ̀. Lẹ́ẹ̀kansí—Ẹ̀mi Mimọ́ ninú wa (nitori tí a ti di àtúnbi) àti Ẹ̀mi Mimọ́ tó wa sórí wa pẹ̀lú ìpèsè ti agbára.

Bibeli kò sọ pé kílóde tí Filippi kò se wàásù fún wọn nipa Ìrìbọmi ti Ẹ̀mi Mimọ́. Ó se é se pé ni kia ni ó kúrò ni Jerusalẹmu lẹ́yìn igbàtí òun tikalarẹ̀ ti gbà ìrìbọmi ti Ẹ̀mi Mimọ́ ní àkókò nà kò mọ̀ pé ó wà fún gbogbo ènìyàn ni. Ohun yówù ti ó le jẹ́, ẹ̀rí ni pé àwọn ènìyàn ti gbàgbọ́ ninú ìhìnrere àti baptisi wọn, wọ́n ti di àtúnbí. Sùgbọ́n kíyèsi bí o ti se pàtàkì tó sí àwọn àpọsteli pé kí àwọn ara Samaria gba Ìrìbọmi ti ẸM Mimọ́ bí wọn wà ni—kíákíá.

Èrò tí wọ́n ní ki ise lati sọ fún wọn bi wọn ó se máa múra, wọ́n kò sọ pé, "Ẹ jẹ́ kí a sọ fún wọn bi wọn o ti se máa múra lótítọ́ tàbí ìgbàti wọn o ma sèsìn" Òfin ìlànà ẹ̀kọ́ kò jọ wọn lojú. Kínni nkan àkọ́kọ́ ti ó jẹ́ wọn lógún? Ìrìbọmi ti Ẹ̀mi Mimọ́! Wọ́n si foríkorí ni kiá ni wọ́n sọ́ fún àwọn ènìyàn na nípa Ìrìbọmi ti Ẹ̀mi Mimọ́.

Nigbanà ni Peteru àti Johannu gbé ọwọ́ le wọn lorí, wọn si gba Ẹ̀mi Mimọ́. Ni ojúkannáà nibẹ̀ ni wọn ti gba Ẹ̀mi Mimọ́. Kín sì ni ẹ̀rí wọn? Mo gbàgbọ́ pé bi ìrírí àwọn ẹlòmíràn nà ni: fífèdèfọ̀

.

> *Ńigbàti Śimońì ri pé nípa gbígbé ọwọ́ lé ni a ti ńti ọwọ́ àwọn àpọ́stéli̇̀ fi Ẹ̀mí Ḿímọ́ fún ni, ó fi owó lọ̀ wọ́n. "o wípé Ẹ fún èmi na ní agbára yìí pẹ̀lú, kí ẹnikẹ́ni tí mó bá gbé ọwọ́ lé, kí o le gba Ẹ̀mí Mímọ́."*

> *Ṕétérù dá a lóhùn wípe, Kí owó rẹ sègbé pẹ̀lú rẹ, nítorí ìwọ rò láti fi owó ra ẹ̀bùn Ọlọrun! Ìwọ kò ní ipa tàbí ìpín nínú ọ̀ràn yíi,*

*nítorí okan re ko se dédé níwájú Ọlorun. Nítorí nà ronúpìwàdà ìwà buburú rẹ yí, kí o sì gbàdúrà sọ́dọ̀ Ọlọrun bóyá yóò dárí ète ọkàn rẹ jìn ọ. Nítorí mo wòye pé, ìwọ wà nínú ìkoro òroro àti ní ìdè ẹ̀sẹ̀''*

*Nígbàna ni Símónì dáhùn,ó sì wipé, Ẹ̀ gbàdurà sọ́dọ̀ Olúwa fún mi, kí ọ̀kàn nínú ohun tí ẹ̀yin ti sọ kí ó máṣẹ*

—Ìse Àwọn Apọsteli 8:18-24

Nigbàti Simoni rí i pé awọn èníyàn gba Ẹ̀mi Mimọ nipa ìgbọ́wọ́lé, ó ni kí àwọn àpọsteli gbà ọwó lati le fún óun ni irú agbára yìí. Simoni ti rí nkankan, àwọn ẹ̀rí ti o máa nsẹlẹ̀ nigbà tí wọ́n bá ti gba Ẹ̀mi Mimọ́. Òun nà fẹ́ irú agbára yìí.

Bayìí, kò sọ pé wọn nfèdèfọ̀ níbẹ̀, sùgọ́n nkankan sẹlẹ̀ níbẹ̀ ti gbogbo wọn le fojú rí. Simoni rí nkan ti ó lágbára, oun nà si fẹ́ irú agbára yìí lati máa fi fún àwọn èniyàn. Mo gbàgbọ́ pé ohun ti ó sọ fi hàn pé àwọn wọ̀nyìí gbà ìrìbọmi yìí bi àwọn ara yókù ti se gbàá wọn sì bẹ̀rẹ̀ sí ní fi èdèfọ̀. Lẹ́ẹ̀kansìi, mo kàn tún fẹ́ sọ fún wa bi àwọn ìjọ ni Jerusalẹmu se nfi ojú wo Ìrìbọmi tí Ẹ̀mi Mimọ bi o ti se pàtàkì tó!

Nigbàti à ti yí Paulu padà bẹ̀rẹ̀ ni ojú ọ̀nà Damasku, arákùnrin ti à npé ni Anania tí a rán sí Paulu làtí gbàdúrà fún nu.

*Ananíà si sọ pé, "Saulu arákùnrin, Oluwa ni ó rán mi, Jesu ti ó fi ara hàn ọ́ ni ọ̀nà tí ìwọ bá wá, kí ìwọ kí o le* ríran*, kí o sì kún fún Ẹ̀mí Mímọ́"*

—Ìse Àwọn Apọsteli 9:17b

Bibeli kò sọ wipé Paulu nfèdèfọ̀ nigbàtí a Baptisi rẹ̀ pẹ̀lú Ẹ̀mi Mimọ, sùgbọ́n a mọ̀ pé o máa nfèdèfọ̀, mo si gbagbọ́ oun nà gbàá bi awọn ẹlòmíràn ti se gbà á ni. O le bèrè pé kin ni idí ti mo se le gbàgbọ́ bẹ̀. Ìyẹ́n rọrùn. nitorí ohun ti Paulu kọ ni, ninú ìwe 1Kọrinti 14:18.

*"Mo dúpẹ́ lọ́wọ́ Ọlọrun ti èmí ń́fọ onírúrú èdè ju gbogbo yín lọ* " 1Kọrinti 14:18.

Bayìí, a le sọ pé Paulu fi èdèfọ̀ nigbàti ó gbà Baptisi ti Ẹ̀mi Mimọ́. Bí o ti se kàá ninú ìwe Ìse Àwọn Àposteli, wà sakíyèsí pé ìrìbọmi yí nlọ lati ìgbà de ìgbà ninú ìjọ ni, kì íse ohun ti o kàn sẹlẹ̀ ni ọjọ́ Pẹntikọsti nikan.

Lẹ́yìn ìgbànà, ninú Ìwe Ìse Awọn Àpọsteli orí kẹwá, Peteru ni a rán lọ si ọ̀dọ̀ àwọn Keferí Ẹ̀mi si darí rẹ̀ lati wàásù ìhìnrere fún wọn. Ranti pé ki ise ohun ti  Peteru máa nse, ẹnití nse Ju, lati lọ sí ilé àwọn Keferí. Ódá lọ síbẹ̀ ni, nitori Ẹ̀mi Mimọ́ ni o darí rẹ̀ síbẹ̀ ninú ìràn.

> *Bí Pétérù  sì ti ń sọ ọ̀rọ̀ wọ̀nyíí ni ẹnu, Ẹ̀mí Mímọ́ bà lé gbogbo àwọn ti ó ńgbọ́ ọ̀rọ̀ náà, Ẹnu si ya àwọn onígbàgbọ ti íkọlà, iye àwọn tí o bá Pétérù wá nitori a tú ẹ̀bùn Ẹ́mi Mímọ́ sórí awọn kẹ̀fèrí pẹ̀lú. Nitorí wọ́n gbọ́, wọ́n ńfọ onírúrú èdè wọn si yin Ọlọrun lógo.*
>
> *Ńígbàna ni Pétérù dáhùn wípe, Ẹnikẹ́ni ha le sọ̀fin omi, kí a ma baptisi àwọn wọ̀nyíí? Tí wọ́n gba Ẹ̀mi Mímọ́ bí àwa. Ó sì pàṣẹ kí á baptisi wọn ní orúkọ Jesu Kristi. Nimgbàna ni wọn bẹ̀ẹ́ kí ó dúró ní ijọ́ melokan"*
>
> —Ìse Àwọn Apọsteli: 10:44-48

Nigbàtí Peteru sì nwàásù Ìhìnrere ti Kristi si ile àwọn Keferi Ẹ̀mi Mimò ba le gbogbo àwọn ti o ngbọ́ ọ̀rọ̀ ìfiránṣẹ́ nà. O kò le ri Ẹ̀mi Ọlọrun, Bawo wá ni wọn ti se mọ̀ pé Ẹ̀mi Mimọ́ ti wà sórí wọn? Ọ̀rọ̀ nà sọ wipé Ẹnu si ya àwọn onigbàgbọ́ ti ìkọlà iye àwọn ti o bá Peterù wá nitorí à tu ẹbùn Ẹ̀mi Mimọ́ tí a tú sorí àwọn keferi. <u>Pẹlú nítorí wọn gbọ́, wọn fọ onirurú èdè wọn sì nyin Ọlọrun lógo.</u>

Kin ni ẹ̀rí tí a ri tí a fi mọ̀ pé Ẹ̀mi Mimọ́ wà nibẹ̀? Peteru ni lati dá ohun tin se ẹ̀rí fún un mọ̀, pé, Ọlọrun ti tẹ́wọ́ gba àwọn ènìyàn wọ̀nyìí. Nitorí ó rí wọn ti wọn nfèdèfọ́ nigbà tí kò ti se ìṣẹ́ ìránṣẹ́ kankan fún wọn nípa Ìrìbọmi ti Ẹ̀mi Mimọ́ ni ẹ̀rí ti o nilò. Peteru *mọ́* pé wọn rí gbà nítorí ti wọn ti gbà Ẹ̀mi Mimọ́ bi òun náà ti gbà—wọn si nfi èdè tuntun sọ̀rọ̀.

Wa rí ìyàtọ̀ nlà ninú ohun ti àwọn ìjọ òde ònìí lérò pé ó se pàtàkì si ohun ti àwọn ìjọ ìgbànì ro pé ó se pàtàki ni ọ̀nà ti Bibeli.

Ọkan ninú àwọn ẹsẹ Bibeli tí mo fẹ́ràn ti o se àlàyé rẹ̀ kedere pé gbogbo ènìyàn ni ó yẹ kí ó sè ìrìbọmi ti Ẹ̀mi Mimọ́, ti o si fi di rẹ̀ mulẹ̀ laísí ìbérè pé ìṣẹ́ ti Ẹ̀mi Mimọ́ ni yatọ si pé àdi àtúnbí, bi ó ti wà ninú ìwe Ìse Àwọn Apọsteli: 19:1-2

> *Ó sìse, nígbàtí Apollo ti wà ní Kọ́ríntì, tí Páulù kọjá lọ ní hà ẹkùn òkè, ó sì wá sí Éfésù: ó sì ri àwọn ọmọ ẹ̀hìn kan ó wí fún wọn pe, Ẹ̀yin ha gba Ẹ̀mí Mímọ́ nà nígbàti ẹ̀yin gbàgbó? Wọ́n sì ti wí fún pé àwa kò gbọ́ rárá bí Ẹ̀mí Mímọ́ kan bá wà"*
>
> —Ìse Àwọn Apọsteli 19:1-2

Nigbà ti Paulu wọ Efesu: ó sì rí àwọn ọmọ ẹ̀hìn kan ó wí fún wọn pé" Ẹ̀yin ha gba Ẹ̀mi Mimọ́ nà nigbàti ẹ̀yín gbàgbọ́?"Ohun àkọ́kọ́ ti ó jẹ Paulu lógun nìyìí ni gbàrà ti o ba àwọn onigbàgbọ́ yìí pade.

Paulu mọ pé kí o ti di àtúnbí tun yàtọ̀ sí ki o tún gbà Ìrìbọmi ti Ẹ̀mi Mimọ́ pẹ̀lú ẹ̀rí ti fifi èdè tuntun sọ̀rọ̀.

Kílóde ti o fi jẹ́ nkan àkọ́kọ́ ti Paulu sọ fún wọn niyìí? Nítorí ohun yi kannà ni Jesu sọ ninú Ìse Àwọn Apọsteli 1:4! Ó mọ̀-ọn-mọ̀ sọ ni, Ẹ máse kúrò ni nilú ha láìsí rẹ̀!" Kínni  nkan tí àwọn àpọsteli se ni Jerusalẹmu nigbàti wọn ri pé àwọn ènìyàn ti o wà ni samaria ti gbọ Ọ̀rọ̀ nà?. Wọn sọ pé" O ya ẹ jẹ́ kú a mura nisisiyìí. Ani lati ri wipé a se bi o t yẹ ki ó rí. Lọ́ síbẹ̀ ki o sì rí dájú pé wọn gbà Ìrìbọmi ti Ẹ̀mi Mimọ́. " Nigbati Paulu, si nlọ si Efesu, o : ó sì rí àwọn ọmọ ẹ̀hìn kan ohun àkọ́kọ́ tí ó wí fún wọn pé" Ẹ̀yin ha gba Ẹ̀mi Mimọ́ nà nigbàti ẹ̀yín gbàgbọ́?

Wọn sì wí fún pé, Rárá, àwa kò gbọ́ rárá bi Ẹ̀mi Mimọ́ kan bá wà."Paulu wa bi wọn pé, ìrìbọmi wo ni ẹ̀yín ti gbà. Wọ́n wi fún pé, "Johannu Onitẹ̀bọmi" Paulu wi pé Ìrìbọmi ti Johanu Onitẹbọmi ni ti ìrònúpìwàdà ó si nsọ fún àwọn èniyàn wipé ki wọn gbà ẹniti o mbọ lẹ́yìn oun gbọ́. Tí nse pé ẹ gbà Jesu gbọ́.

Bi wọn ti se ngbọ́ èyí, à si nbaptisi

**NIBÁYÌÍ, MO GBÀGBỌ́ PÉ KÓKÓ Ọ̀RỌ̀ ÀRÍYÀNJIYÀN NI NÍNÚ Ọ̀PỌ̀ ÀWỌN ÌJỌ NITORÍ KÌ ÍSE PÉ KÒSÍ NINÚ BIBELI, BIKÒSE NITORÍPÉ ÈSU KÓRÌRA RẸ̀ PÚPỌ̀.**

wọn sinú orukọ Jesu Oluwa( ìrìbọmi sinú omi). Lẹ́yìn ìgbànà, ti Paulu gbé ọwọ́ le wọn, Ẹ̀mi Mimọ́ si bá lé wọn wọn si bẹ̀rẹ̀ si ni fèdèfọ̀. Kiyèsi nigbàti Paulu bèrè ìbérè ó ti rò pé wọn gbàgbọ́ ninú Jesu. Idí sì nìyìí ti o fi bi wọn pé “Se wọn ti gbà Ẹ̀mi Mimọ́ lati ìgbà ti wọn ti gbàgbọ́? Ìrìbọmi ti Ẹ̀mi Mimọ́ yàtọ̀ gedégédé si didi àtunbí.

Nibayìí, mo gbàgbọ pé kókó ọ̀rọ̀ àriyànjiyàn ninú ọ̀pọ̀ àwọn ìjọ nitori kì ise pé kòsí ninú Bibeli, bíkòse nitorípe esu kórírà rẹ̀ pupọ.

Nitori pé ti oó ba jẹ́ ni ti agbára, ti ó ba jẹ́ ọnà si agbàra lati yi aye àwọn èniyàn padà àti lati jẹ́ ẹlẹ́ri fún gbogbo ayé, nigbànà ni wà jẹ́ alátakò si ọlọrun ti ayé yìí, à sí mọ iru nkan ti ìpinu yìí le jẹ́. Ìrìbọmi ti Ẹ̀mi Mimọ́ fún wà ni ibi ìpamọ́ agbára, agbára Ọlọrun, lati le se iṣẹ́ Jesu ki a bá le yin Ọlọrun nìkan lògo!

ORÍ KẸFÀ

# GBA GBOGBO ÀDÚRÀ NÍ ÌFÈDÈFỌ̀?

Bóyá o ti ngbọ́ ti ẹnikan nsọ wípé wọn kì í fèdèfọ̀ àti pé wọn kò gbàgbọ́ pé gbogbo ènìyàn ni o le fèdèfọ̀ tàbi lóyẹ ki o má fèdèfọ̀. Nigbàànà ni wọn o wá má ka ẹsẹ Bibeli yìí fún ọ 1 Kọrinti 12:27-30 gẹ́gẹ́ bi ìdí tí wọn fi gbagbọ́ bẹ̀. Wọn ó tún tọ́ka Paulu pé, oun gan sọ wípé ki se gbogbo èniyàn ni ó nfi onirúru èdè fọ̀. Ó dáa, ẹ jẹ́ ki a lọ wo ohun ti ókàn ki a sì wòó bóyá ohun ti Paulu nsọ nìyìí.

*Ǹjẹ́ ara Kristi ni ẹ̀yin íse, olúkúlúkù yin sì jẹ́ ara rẹ̀. Ọlọrun sì gbé àwọn míràn kalẹ̀ <u>nínú ìjọ,</u> èkínní àwọn apọ́stélì, èkejì àwọn wòlíì, ẹ̀kẹta àwon olùkọ́ni, lẹ́hìnna ísẹ́ ìyanu , lẹ́hìnna ẹ̀bùn ìmúláradá, ìrànlọ́wọ́, ebùn àkóso, onírúrú èdè. Gbogbo wọn ni íse apọ́stélì bí? Gbogbo wọn ní ise wòlíì bí? Gbogbo wọn ní se isẹ́ olùkọ́ni bí? Gbogbo wọn ní ise isẹ́ ìyanu bí? Gbogbo wọn ní ó ní ẹ̀bùn ìmúláradá bí? <u>Gbogbo wọn ni ńfi onírúrú èdè fọ̀ bi</u>? Gbogbo wọn ní ńse ìtumọ̀ bí?*

—1 Kọrinti 12:27-30.

Nínu lẹ́tà yìí, Paulu nsọ fún àwọn ìjọ ni kọrinti bi wọn ti se le máa sìṣẹ́ létòlétò ti gbogbo wọn yóò fi le ma sìṣẹ́ ìránṣẹ́ papọ̀ ninú àpéjọpọ̀ ninú ìjọ. Ni àsikò yìí gbogbo wọn ngbìyànjú lati se ju ara wọn lọ pẹ̀lú ẹbùn ẹ̀mi àti oniwáasu ti wọn fẹ́ràn julọ. Paulu wá nsọ fún wọn bí wọn ti se le máa sìṣẹ́ gẹ́gẹ́ bi ara kan àti ninú ìfẹ́. Ó yá ẹ jẹ́ ki a lọ wòó ninú 1Kọrinti 12:27-28:

*Njẹ ara Kristi li ẹnyin iṣe, olukuluku nyin si jẹ ẹ̀ya ara rẹ. Ọlọrun*

*si gbé awọn miran kalẹ ninu ijọ,? (Mo gba o niyanju´ ki o fa ila si ni idi) ekini awọn aposteli, ekeji awọn woli, ẹkẹta awọn olukọni, lẹhinna iṣẹ iyanu, lẹhinna ẹbun imularada, iranlọwọ, ẹbùn akoso, onirũru ède.*

Paulu tún tẹsíwajú, sùgbọ́n mo fẹ́ da dúró nitorí mo fẹ́ lati sọ̀rọ̀ nipa rẹ̀ diẹ "Ninú ìjọ." Ó nsọrọ nipa ìpejọpọ̀ àwọn ìjọ. A le rí àmọ̀dájú yìí ninú ìwe 1Kọrinti 14:18-19 nibití Paulu ti tún ti lo gbólóhùn ọ̀rọ̀ yìí:

*"Mo dúpẹ́ lọ́wọ́ Ọlọrun ti èmí ńfọ onírúrú èdè ju gbogbo yín lọ" Sùgbọ́n mo fe kín kúkú fi òye mi sọ ọ̀rọ̀ márun NÍNÚ ÌJỌ kín le kọ́ àwọn ẹlòmíràn pẹ̀lú jú ẹgbàrún ọ̀rọ̀ ní èdè àìmọ.*

—1Kọ́ríntì 14:18-19

Paulu ni "Mo dúpẹ́ lọ́wọ́ Ọlọrun tí èmi nfọ onirúrú èdè ju gbogbo yin lọ, "**Sùgbọ́n nínú ìjọ….**" Gbolóhùn ọ̀rọ̀ yìí lẹ́ẹ̀kansi, Níbíyìí o hàn kedere pé Paulu nsọ̀rọ̀ nipa àpéjọpọ̀ àwọn ìjọ ki ìse ti ara Kristi nigbogbo àgbáyé. Gbogbo wa ni a mọ pé àra Kristi ni Paulu nse, "Ìjọ." lóòtọ́ bẹ́ẹ̀ni ó jẹ́. Ó si wa sọ pé inu òun dùn ti on nfọ onirúrú èdè ju gbogbo àwọn onígbàgbọ́ ni Kọrinti lọ. Ó sọ pé nitorí àwọn ijọ kọrinti nyọ̀ ninú agbára wọn tuntun lati sọ̀sọ̀ ni èdè àìmọ̀, àti wọn ti kurò lábẹ́ àṣẹ/ èto ti wọn nfa ipòrurù/ da nkanrú

Ohun ti ó nsọ ni pé, ẹ̀yìn ara, èmi nfédèfọ̀ ju gbogbo yín lọ, sùgbọ́n ọ̀nà ti à le gbà sé "ninú ìjọ" na wà létòletò ti kò fi ni dojúrú tàbi dàrúdàápọ̀." Ó tẹ̀síwaju lati sọ pé, ninú ìjọ (àpéjọpọ̀ àwọn onigbàgbọ́), on yóò sọ̀rọ̀ ninú òye (ni èdè ti gbogbo gbọ́) ki àwọn ẹlomiran leè ni oye àti satunse.

Ninú iṣẹ́ ìsìn ìjọ fúnrarẹ̀, awọn kan yóò ma sisẹ ninú ẹ̀bún ti ìfèdè titun sọ̀rọ̀ àti ìtúmọ̀ èdè, bi àti kọsílẹ̀ ninú *1*Kọrinti *12*,sugbọ́n ki íse gbogbo rẹ̀ ni tabi ni o yẹ ki o máa siṣẹ́ ninú ẹbùn yìí fún ìdi àti le fi gbogbo ẹ̀ṣẹ̀ ìjọ múlẹ̀. Paulu kòda bi ò ti se le dín awọn ọ̀pọ̀ ènìyàn kù ti ò ma fi èdè fọ̀ àti bi awọn mẹta ti wọn ó ma se ogbufọ̀ rẹ̀ ninú ìjọ.

*"Bí ẹnìkeni bá fi èdè fò—kí ó jẹ̀ ènìyàn méjì—tàbí ó pọ̀ tán—kí ó jẹ́*

*mẹ́ta, àti èyíni nì ọ̀kọ̀kan; kí ẹnìkan si jẹ́ ògbufọ̀"* (1Kọrinti 14:27)

Torinà, nigbàti Paulu nsọ pé ki se gbogbo wọn ni o nfọ́ onirúrú èdè, àwọn ìjọ" tàbi àpéjọ́pọ̀ àwọn ìjọ ni ó nsọ.

Ó ní lati ni òye pè gbogbo ọnigbàgbọ́ ni ó ni agbára lati le fèdèfọ̀, sugbọ́n ki íse gbogbo èniyàn ni o ni ìmísí ore-ọ̀fẹ́ lati le gbé ẹbun ti ìfèdèfọ̀ tàbi ogbufọ̀ wọ ninú ìsìn ijọ. Tí o ba ni irú ìmísí yìí lati jade ninú ẹbùn ìsìn ìjọ, Bibeli sọ pé ki o gbàdúrà lati le ma se ógbufọ̀.

*"Ẹnití ńsọ̀rọ̀ ní èdè àimọ̀ gbàdúrà kí ó le má se ìtumọ̀ ohun tí ó bá sọ"* (1Kọrinti 14:13b)

Mo ní ìgbàgbọ́ wípé ẹnikẹ́ni ti o bá nfèdèfọ̀ ó yẹ ki o le má tumọ èdè na ninú ìsìn nitori ìṣẹ́ ìfiránṣẹ ti nti ìnú wọn jáde wá.

Kílóde ti o fi gbọ́dọ̀ gbàdúrà ninú ẹ̀mi/ ìfèdèfọ́? Èsu kòríra àwọn onigbàgbọ́ ti wọ́n mọ̀ bi a ti ngbàdúrà ninú Ẹ̀mi(ìfèdèfọ̀), mo si fẹ̀ mọ̀ dajú pé ó mọ́ ìdí. Nigbati Paulu sọ pé òun dúpẹ́ ti òun fi èdè fọ ju gbogbo yin lọ, ó gbọ́dọ̀ ni ìdí ti o fi lerò bẹ́ẹ̀. Paulu sọ ọ̀rọ̀ kan ninú ìwe 1Kọrinti 14: 4 ti ó yẹ̀ ki a lọ kà.

*"Ẹniti ńsọ̀rọ̀ ni èdè àimọ̀ ńfi ẹsẹ̀ ara rẹ* ***múlẹ̀****; sùgbọ́n ẹniti nsọtẹ́lẹ̀ ńfi ẹsẹ̀ ìjọ* ***múlẹ̀"*** (1Kọ̀ríntì 14:4)

Ẹjẹ́ ki a wádí jinlẹ̀ díẹ̀ si. Kin ni o túmọ si lati fi ẹṣẹ múlẹ̀? Gbólóhùn yìí fẹṣẹ̀mulẹ̀ túmọ̀ si, "lati kẹ́kọ́, tàbi ànfà, pàápá jùlọ́ ni ti ìwà tàbi t'ẹ̀mi; lati kún fún ẹ̀mi."[2]

Wà á gbà pẹ̀lú mi pé ọ̀pọ̀ ìgba ni à máa nílò ìtọni lati mọ ọ̀na ti a ó gbà, lati ni òye nkan ti o nsẹlẹ̀, tàbi lati le se ìpinnu ti o tọ. Gbogbo nkan wọ̀nyìí ni gbígbàdúrà ninú Ẹ̀mi le ràn ọ́ lọwọ́ lati se: lati fi ẹṣẹ̀ rẹ múlẹ̀ tàbi mú ìtọ́ni wá sinú ayé rẹ. Paulu se àlayé yìí ninú ìwe Romú 8:26-27:

*Bẹ́ẹ̀ gẹ́gẹ́ ni Ẹ̀mí pẹ̀lú sì ń ran <u>àilera wa</u> <u>lọ́wọ́</u>: nítorí a kò mọ̀ bí a ti ńgbàdúrà gẹ́gẹ bí o ti yẹ: sùgbọ́n Ẹ̀mí tìkararẹ̀ ńfi ìroro tí a kò le fi ẹnu sọ bẹ̀bẹ̀ fún wa. Ẹnití ó si inú ọkàn wa wò, ó mọ ohun ti inú Ẹ̀mí*

**"BẸ́Ẹ̀ GẸ́GẸ́ NI Ẹ̀MI PẸ̀LÚ SÌ NRAN ÀÌLERA WA LỌ́WỌ́ NÍTORÍ A KÒ MỌ BÌ A TÍ ÍGBÀDÚRÀ GẸ́GẸ́ BÍ O TI YẸ**

**—ROMU 8:26A**

*nítorí ó mbẹ̀bẹ̀ fún àwọn ènìyàn mimọ́ gẹ́gẹ́ bí ìfẹ̀ Ọlọrun*

Paulu sọ fún wa pé a ni ìsòro àti àìlera;"Ao si mọ ohun ti a fẹ́ gbàdúrà fún" O le bèrè pé, Kilóde ti o fi jẹ́ àìlera? A le mọ ìdí ti ó fi jẹ́ àìlera nigbàti a ba lọ ka ìwe ẹ́ Johanu 5:14-15

*Èyí sì ni ìgboyà tí àwa ní níwájú rẹ̀, pé bí àwa bá bèrè ohunkohun gẹ́gẹ́ bi ìfẹ́ rẹ̀, ó ńgbọ́ ti wa. Bí àwa bá sì mọ̀ pe ó ńgbọ́ ti wa—Ohunkóhun tí àwa bá bèrè—àwa mọ́ peáwaríìbeèrèti àwa ti bèrè lọ́dọ̀ rẹ̀ gbà''*

Laímọ̀ tàbi ni ìgboyà ninú ìfẹ́ Ọlọrun, àwa kò ni le siṣẹ́ ninú ìgbàgbọ́ (àdehùn ti a ni pẹ̀lú Ọlọrun) ti a kò ba si le siṣẹ́ ninú ìgbàgbọ́, a jẹ́ wípé awà ni àìlera nitòótọ nitori à kò ni le gbà ore-ọ̀fẹ́ tàbi agbára ti Ọlọrun laísí ìgbàgbọ́ nibẹ̀. Torínà Paulu sọ pé nitorí a kò mọ bi a ti se ngbàdúrà ipo àìlera ni ti ìfèdèfọ̀ si le se ìrànlọ́wọ́. Ẹ jẹ́ ki a lọ́ ka ẹsẹ̀ nà lẹ́ẹ̀kansi.

*"Bẹ̀ẹ̀ gẹ́gẹ́ ni Ẹ̀mí pẹ̀lú sì ń ran àilera wa lọ́wọ́. <u>nítorí a kò mọ̀ bí a ti ńgbàdúrà gẹ́gẹ bí o ti yẹ.</u>*

—Romu *8:*26a

Àìlera wa ni pé à kò mọ̀ bi a ti ngbàdúrà! Bibeli kò sọ fún wa ẹniti ó yẹ ká fẹ́, ibiti ó yẹ ki a gbé, tàbi ìṣẹ́ ti o yẹ́ kí a se. Laì jẹ́ pé a mọ́ ìfẹ́ Ọlọrun, a kò le mọ̀ ati gbàgbọ́ pé a gbà ìdàhùn lati ọ̀dọ̀ Ọlọrun nigbàti a bá gbàdurà. Lẹ̀ẹ̀kansi, àìlera nlá ni! A kò ni ìgboyà kankan ninú Ọlọrun nigbàti a kò mọ ohun ti ìfẹ́ Rẹ̀ jẹ́. Sùgbọ́n ọ̀nà wà ti a fi le dá ìfẹ́ Ọlọrun mọ̀ ninú ipòkípò tí a bá wà ní ayé. Ọ̀nà wà ti a fi le mọ ìfẹ́ Ọlọrun tí o dajú ti a ó si lo ìgbàgbọ́ àti ìgboyà wa.

Nkan tí Paulu nsọ̀rọ̀ nipa rẹ nìyìí. Ìfẹṣẹ̀mulẹ̀ ti o nsọ̀rọ̀ nipa rẹ̀ túmọ sí kí o ni àyè si ìrú àwọn ìmọ́ yìí—ìmọ̀ tí ó wá nipa Ẹ̀mi Ọlọrun. A sì wá ngbọ́ ti Ẹ̀mi nipa gbúgbàdúrà ninú Ẹ̀mi, tàbi ìfèdèfọ̀. Ti à bá ntẹ̀lé ìmọ̀ràn Paulu si wajú sí i ninú ìwe Romu 8:26b-27, Ẹ jẹ́ ki a lọ kàá:

*Sùgbọ́n Ẹ̀mí tìkararẹ̀ ńfi ìroro tí a kò le fi ẹnu sọ bẹ̀bẹ̀ fún wa. Ẹnití ó si inú ọkàn wa wò, ó mọ ohun ti inú Ẹ̀mí nítorí ó mbẹ̀bẹ̀ fún àwọn ènìyàn mimọ́ gẹ́gẹ́ bí ìfẹ̀ Ọlọrun.*

Bayìí Paulu kò sọ fún wa pé à wa ni ìrora ngbàti à gbádúrà ninú Ẹ̀mi, bikòse pé, dipò bẹ́ẹ̀, Paulu ntọkasí ẹṣẹ ti a ti kà sẹ́yìn.

*Nitorí àwa mọ̀ pé gbogbo ẹ̀dá ni ó jùmọ̀ nkérora tí o si ńrọbí pọ̀ títí di ìsisìyìí. Kì si íse àwọn nkan sùgbọ́n àwa tìkara wa pẹ̀lú, ti ó ni àkọ́so Ẹ̀mí àní àwa tìkarawa ńkérora nínú ara wa, àwa ńdúró de ìsodọmo, àní ìdánde ara wa. Nítorí ìrètí ni a fi gbà wá là: sùgbón ìrètí, nitorí tani ńretí ohun tí o bárí? Sùgbọ́n bí àwa bá ńretí èyí tí àwa kò rí, ǹjẹ́ àwa ńfi sùúrù dúró dèé.*

*Bẹ́ẹ̀ gẹ́gẹ́ ni Ẹ̀mí pẹ̀lú sì ń ran àilera wa lọ́wọ́: nítorí a kò mọ̀ bí a ti ńgbàdúrà gẹ́gẹ bí o ti yẹ: sùgbọ́n Ẹ̀mí tìkararẹ̀ ńfi ìroro tí a kò le fi ẹnu sọ bẹ̀bẹ̀ fún wa. Ẹnití ó si inú ọkàn wa wò, ó mọ ohun ti inú Ẹ̀mí nítorí ó mbẹ̀bẹ̀ fún àwọn ènìyàn mimọ́ gẹ́gẹ́ bí ìfẹ̀ Ọlọrun.*

—Romu 8:22-27

Paulu nlo gbólóhùn ọ̀rọ̀ yìí ìrora nibiyìí bi àpèjuwe tàbi àpẹẹrẹ ohun ti ó nsẹlẹ̀ ninú wà. À nkérora ninú bí obinrin ti ò nrọbí ti ó fẹ́ bímọ. Tì ó jẹ́ wipé, à nbí nkankan lati ìnú Ẹ̀mi Ọlọrun tí ó wà ninú wa,à ngba ohun titun, ohun ti kò ti wà tẹ́lẹ̀ rí; tàbi o le sọ pé ohun tí kì se tìkálárawa. Torinà "à bì" ìmọ̀ ohun ti a kò mọ̀, Nkan titun, wá láti inú ẹ̀mi wa nipaṣẹ́ gbígbàdúrà ninú Ẹ̀mi. Bibeli sọ fún wa pé, Ẹ̀mi Ọlọrun ngbàdúrà ti ìfẹ́ pípé ti Ọlọrun fún gbogbo ipòkípò lati ipaṣẹ̀ ẹ̀mi wa. Ó sọ pé Ọlọrun tìkararẹ̀ ngbàdúrà fún wa, nipaṣẹ̀ ẹ̀mí ènìyàn wà, pẹ̀lú ìrora ti a kò le fẹnu sọ (sàlàyé ni yéké yéké).

Ohun ti a rí níbíyìí ni pé Ẹ̀mi Mimọ́ ní yóò sìpẹ̀ fún wa pẹ̀lú ìrora (Rọbí) ní lílo àwọn ọ̀rọ̀ ti a kò le sàlàye, àwọn ọ̀rọ̀ ti kò yé wa (ìfèdèfọ̀). Ẹniti ó si nwá inú ọkàn mọ ọkàn ti Ẹ̀mi nitori Ẹ̀mi (Ẹ̀mi Ọlọrun) nsìpẹ̀ fún àwọn ènìyàn mimọ́ ni botiyẹ̀ pẹ̀lú ìfẹ́ pípé ti Ọlọrun. Ẹ̀mi Ọlọrun ngbàdúrà ni ti ìfẹ́ pípé Ọlrun fún ipò kọ̀kan **nípasẹ̀ ẹ̀mí rẹ nígbàtí ó bá**

**<u>ńgbàdúrà nínú Ẹ̀mí (ìfèdèfọ̀)</u>**

Torínà, awà ni ipò àìlera nigbàti a kò ba mọ ìfẹ́ Ọlọrun. Ìgbàgbọ́ kò le wá niwọ̀n ìgbà tí a kò bá tíì mọ ìfẹ́ ti Ọlọrun. Pàulu nsọ pé tí a ó ba gbàdúrà ninú Ẹ̀mi, Ẹ̀mi ti Ọlọrun ni yóò gbàdúrà nipaṣẹ̀ wa ni ti ìfẹ́ pípé ti Ọlọrun fún ayé wa tàbi ninú ipòkípò.

Gẹ́gẹ́ bí Ẹ̀mi Ọlọrun ti nse gbàdúrà nípaṣẹ̀ wà ninú ìfèdèfọ̀, báwo ni a se máa fi ẹṣẹ̀ múlẹ̀ niwọ̀n ìgbà ti a ò mọ ohun tí a nsọ? A rí ìdáhùn ninú ìwe miràn ti Paulu tún kọ.

> *Sùgbọ́n gẹ́gẹ́ bí a ti kọ pé, ohun tí ojú kò rí, àti tí etí kò ti gbọ́, tí kò si wọ ọkàn ènìyàn lọ, ohun wọnnì ti Ọlọrun ti pèsè sílẹ̀ fún àwọn tí o fẹ́ẹ–sùgbọ́n Ọlọrun ti sí wọn payá fún wa nípa Ẹ̀mí rẹ̀.*
>
> *Ẹ̀mí ńwadi ohun gbogbo, àní ohun ìjìnlẹ̀ ti Ọlọrun. Nítorí tani nínú ènìyàn tí ó mọ ohùn ènìyàn tán, bíkòse ẹ̀mí ènìyàn tí ó wà nínú rẹ̀? Bẹ́ẹ̀ni kò sí ẹnìkan tí o mọ ohun Ọlọrun bíkòse Ẹ̀mí Ọlọrun. Sùgbọ́n àwa ti gbà, ki íse ẹ̀mí ti ayé, bíkòse Ẹ̀mí ti íse ti Ọlọrun; kí àwa kí ó le mọ ohun tí a fifún wa ní ọ̀fẹ́ láti ọ̀dọ̀ Ọlọrun wá. Ohun na tí àwa sì ń sọ, ki íse nínú ọ̀rọ̀ ti ọgbọ́n ènìyàn ńkọ́ni, sùgbọ́n èyíti Ẹ̀mí Mímọ́ ńfi ńkọ́ni; èyítí a ńfi ohun Ẹ̀mí wé ohun Ẹ̀mí'.*
>
> —1Kòríntì 2:9b-13

Ni àkọ́kọ́, ohun ti Paulu nsọ ni wipé à ni ẹ̀tọ si àwọn nkan ti a kò ti gbọ́ rí, rí tàbi rò rí, gẹ́gẹ́ bi mo ti npin pẹ̀lú rẹ. Sùgbọ́n ó tún tẹ̀síwajú lati sọ fún wa bí àwọn nkan wọnyìí ti le siṣẹ́:

> *Nítorí tani nínú ènìyàn tí ó mọ ohùn ènìyàn tán, bíkòse ẹ̀mí ènìyàn tí ó wà nínú rẹ̀? Bẹ́ẹ̀ni kò sí ẹnìkan tí o mọ ohun Ọlọrun bíkòse Ẹ̀mí Ọlọrun.*
>
> —1Kòríntì 2:11

Kin to kúrò lórí ẹ̀kọ́ yí, ani lati ni ìpìlẹ̀ tó dájú lorí ohun ti à nsọ láfikún. Gẹ́gẹ́ bi ìwe ti sọ pé ọ̀na mẹta ni a pín sí: ẹ̀mi, ọkàn àti ara.

> *Kí Ọlọrun àlàáfìa tìkararẹ̀ kí o sọ yín di mímọ́ pátápátá kí a sì pa ẹ́mi àti ọkàn ati ara yiń mọ́ pátápátá ni aìlábùkù ní ìgbà wíwá Oluwa Jesu Kristi.*
>
> —1 Tessalonika 5:23,

Ẹ̀mi wa ni ara Ọlọrun lára wa, ọkàn wa ni ọkàn wa, ifẹ́, àti ìmọ̀lára; ati ara wa ni àgọ́ ara wa; Paulu nsọ nibiyìí pé ọkàn (ọkàn, ìfẹ́, àti ìmọ̀lára) àti ẹ̀mi sùnmọ ara wọn pípọ̀ ti ẹ̀mi wa si mọ̀ ohun ti èro wọn jẹ́.

Òtítọ́ ni bi o ti se só. Ọkàn wa le mọ èrò wa lati inú ẹ̀mi wa. Paulu sọ pé Ẹ̀mi Ọlọrun mọ èrò Ọlọrun èyí ni ohun tí a sì ti rí gbà, Ẹ̀mi Ọlọrun Kí àwa ba **le mọ̀** ohun ti Ọlọrun ti fifún wa lọ́fẹ́.

> *Sùgbọ́n àwa ti gbà, ki íse ẹ̀mí ti ayé, bíkòse Ẹ̀mí ti íse ti Ọlọrun; kí àwa kí ó le mọ ohun tí a fifún wa ní ọ̀fẹ́ láti ọ̀dọ̀ Ọlọrun wá. Ohun na tí àwa sì ń sọ, ki íse nínú ọ̀rọ̀ ti ọgbọ́n ènìyàn ńkọ́ni, sùgbọ́n èyíti Ẹ̀mí Mímọ́ ńfi ńkọ́ni; èyítí a nfi ohun Ẹ̀mí wé ohun Ẹ̀mí"*
>
> —1Kọ́ríntì 2:12-13

Paulu tẹ̀síwáju lati sọ pẹ̀ ìmọ̀í a kò mọ̀ yií, Ìmọ̀ tí a kò mọ̀ sùgbọ́n ti a fi hàn fún wa nipaṣẹ̀ Ẹ̀mi Ọlọrun, ohun ni àwọn ọ̀rọ̀ ti à nsọ èyítí a fi kọ́ wa nipa Ẹ̀mi ti Ọlọrun, kì íse àwọn ọ̀rọ̀ ti à nsọ nipa oye tàbi edè ti ara wa bikòse ọ̀rọ̀ t'ẹ̀mi. Àwa mọ̀ pé Paulu nsọ nípa Ìfèdèfọ̀ gbàdúrà nigbàti ó ní àwa ngbàdúrà pẹ̀lú ọ̀rọ̀ t'ẹ̀mi nitorí ó lo irú itumọ yìí lati sàpèjúwe fifi èdèfọ̀ ninú 1Kọrinti 14:14-15.

> *Nítorí bí èmi bá ńgbàdúrà ní èdè àimọ̀, ẹ̀mí mí ńgbàdúrà, sùgbọ́n òye mí jẹ́ alaíléso. Ǹjẹ́ kín ni èmí ó se? Èmi ó fi ẹ̀mí gbàdúrà, èmi ó fi òye gbàdúrà pẹ̀lú: èmi ó fi ẹ̀mí kọrin, èmi ó sì fi òye kọrin pẹ̀lú.*

Paulu nlo gbólóhùn ọ̀rọ̀ yìí "gbàdúrà ninú ẹ̀mi" nsọ ni ti ìfèdèfọ̀. A tun le rò pé Paulu nsọ́ ohun kan náà nipa fifi èdè fọ̀ nigbàti ó ni pé àwa sọ̀rọ̀ pẹ̀lú àwọn ọ̀rọ̀ èrò ti Ẹ̀mi Mimọ́ fi nkọ́ni.

*Nítorí ẹnití ńsọ̀rọ̀ ní èdè àìmọ̀. Kò bá ènìyàn sọ̀rọ̀. bíkòse Ọlọrun: nítorí kò sí ẹnití ó gbọ́: sùgbọ́n nípa ti Ẹ̀mí <u>ó ńsọ ohun ìjìnlẹ̀</u>*

—1Kọ́ríntì 14:2

Lẹ́ẹ̀kansí, Paulu sọ̀rọ̀ nipa émi wa bi agbára lati le sọ àwọn ti a kò ti rí,gbọ́ tàbi ni ìmọ̀ rẹ̀, tàbi bi Paulu ti sọ  pé "àwọn ohun ìjìnlẹ̀." Bakannà kiyèsi ẹsẹ Bibeli ti Paulu ti sọ ti ohun ìjìnlẹ̀ <u>pẹ̀lú ẹ̀mi wà,</u> kì íse Ẹ̀mi ti Ọlọrun. Báwo wá ni ohun tí a kò mọ̀ se le wọ inú ẹ̀mi wa? Èyí ti o sọ yi rọrùn! Nipaṣẹ̀ Ẹ̀mi Ọlọrun, ti n se ọkansoso pẹ̀lú ẹ̀mi wa.

**ÌRÌBỌMI TI Ẹ̀MI MIMỌ́ JẸ́ OHUN ÌJA IBI ÌKỌ̀KỌ̀ TI ỌLỌRUNẸ́ Ó LE KÁ ÀGBÀSÍLẸ̀ ÌFẸ́ RẸ̀ SÍNÚ AYÉ LÁÌJẸ́ KÍ ÈSÙ MỌ OHUN TÍ Ó NLỌ.**

*Nítorí tani nínú ènìyàn tí ó mọ ohùn ènìyàn tán, bíkòse ẹ̀mí ènìyàn tí ó wà nínú rẹ̀? Bẹ́ẹ̀ni kò sí ẹnìkan tí o mọ ohun Ọlọrun bíkòse Ẹ̀mí Ọlọrun.*

—1Kòríntì 2:11

Nigbàtí ẹ̀mi wa bá nronú lorí àwọn èrò Ọlọrun, ọkàn wan a yóò ma ro àwọn èrò nà. Nigbati ọkàn wa bá nro awọn èrò ti Ọlọrun, a npèé ni "Ìfihàn"  tí nse "Níní ìmọ̀/sàlàyé" tabi bi Paulu ti sọ "sàtúnse/fi ẹsẹ̀ múlẹ̀" Nibáyìí o ti mọ ìdí ti Paulu fi sọ̀ pé òun láyọ̀ pé òun fọ onírúrú èdè gbàdúrà ju ẹnikẹ́ni lọ́; Óni ànfani mi mọ ìfẹ́ ti Ọlọrun ninú ipòkípò gbogbo.

Nkan tí Paulu ntọ́kasí nínú ìwe 1Kòríntì 2:15-16.

*Sùgbọ́n ẹniti ó wà nípa ti ẹ̀mí ńwádi ohnu gbogbo, sùgbọ́n kò sí ẹnikẹ́ni tí ńwadi rẹ̀: Nítorítani ó mọ inú Oluwa, tí yóò fi má kọ́ ọ? sùgbọ́n àwa ní Kristi.*

A kò ní gbèdéke ti nwádí ẹnikẹ́ni, sùgbọ́n à le se ìwadi nipa ohun gbogbo pẹ̀lú ìrànlọ́wọ́ Ọlọrun. Ìròyìn ayọ̀ nla niyìí.!  Àwa ni agbára yìí, nipa gbígbàdúrà ninú Ẹ̀mi (ifèdèfọ̀), lati le gbà awọn ohun ijìnlẹ̀ ti ìjọba

Ọlọrun; awọn ohun ti a kò mọ̀; ati nipa ìmọ̀ yìí, a o le se ìwádi ti o yẹ àti se ìpínnu lori ohun gbogbo!

Ìrìbọmi ti Ẹ̀mi Mimọ́ jẹ́ ohun ìjà ibi ìkọ̀kọ̀ ti Ọlọrun! Ó le se àgbasilẹ̀ àwọn ìfẹ́ Rẹ̀ sinù ayé làijẹ́ ki èsù mọ ohun ti o nlọ́. Kóda, gbígbàdúrà ninú Ẹ̀mi jẹ́ ara ìsọ́ra t'ẹ̀mi ninú ìwe Efesu 6:18a:

*Pẹ̀lú gbogbo àduŕà àti ẹ̀bẹ̀ ni kí ẹ má a gbàdúrà nígbàgbogbo.*

Gbígbàdúrà ninú Ẹ̀mi gbàwá ni ayè lati le mọ àwọn ìlanà ète ti yóò mú wà le sẹ́gun àwọn ọ̀tá, tàbi lati le ló àwọn ọgbọ́n ti kò wọpọ̀ lati bórí wọn.

Àwọn ànfani ti a ni ni lati se ìpìnu ti ó yẹ ninú ayè nipa mi mọ́ ọkàn Kristi. Mo lerò pé wa gbà pẹ̀lú mi pé èyí se kókó! Èmi náà ri pé bẹ́ ló rí!

Gẹ́gẹ́ bí àpẹẹrẹ, mo le rántí ìgbà ti mo fẹ́ se ìpìnu tótóbi kan nípa oko-òwò mi. Alágbàtà ti a jọ nsiṣẹ́ pọ̀, ti o nsojú ọkan lara àwọn onibarà mi, ni ó hún halẹ̀ pé òun yóò gbé ilé -iṣẹ́ mi lọ sile ẹjọ́ nitorí èmi kò setan lati bá a lọ si ile tuntun miràn. Ó si fẹ́ ki a jọ máa siṣẹ́ papọ̀ lẹ́yìn ìgbà ti o ti kúrò ni ọ̀dọ̀ onibarà ti à jọ nso wò pọ̀ tẹ́lẹ̀. Mo nifẹ́ alágbàtà mi, súgbọ́n mo rò pé o yẹ kin jẹ́ olótítọ́ si ile-iṣẹ́ ti mo ti nsiṣẹ́ fún, ki ise òun. Sibẹ̀sibẹ̀, ilé-iṣẹ́ tí a ti ó nsiṣẹ́ fún sì ní, kóda, ki o kó gbogbo awọn oníbárà ni o le ba lọ sí ile-iṣẹ́ tuntun tí o sẹ̀sẹ̀ ti gba iṣẹ́, Ti mó ba tẹ̀le mi o tìí se àsìse kankan pẹ̀lú rẹ̀, sibẹ̀, kò dun mọ́ mi lati fi tipátipá tẹ̀le lọ. Ilé-isẹ́ tuntun yìí si fi gbogbo ìgbà dára si mi.

O nhalẹ̀ mọ mi lati pè mi lẹjọ́ nitori bi osù melo sẹ́yìn ti ó bi mi pé a o jọ ma lọ si ibi iṣẹ́ tuntun ti o sẹ̀sẹ̀ gbà. Tí mi o tilẹ̀ ronú nipa rẹ̀, ti mo si sọ pé moi o lọ. Ó wa sọ pé òun ti fi ọkan si pé ma wà pẹ̀lú òun ni ibisẹ́ nà nigbà ti oun pinnu lati parọ̀ àwọn ilé iṣẹ́ nà. Sugbọ́n nibayìí bi ọjọ́ na ti nsúnmọ fún un lati lọ, ara mi kò gbà á. Torinà, mo lọ gbàdúrà ninú Ẹ̀mi fún bi àwọn ọjọ́ diẹ̀.Sugbọ́n, sibẹ̀ mi o gbọ́ ìdáhùn ti mo nilò.

Drenda ati èmi máa nkó àwọn ọmọ wa lọ si ibùdò ìgbàfẹ̀ kan ti kò ju bi ìrìn wákàti mejì lọ si ọ̀dọ̀ wa ti à npè ni Cedar Point. Ibùdò igbàfẹ́ yìí ni o si fẹ́ẹ̀ tobijulọ ni orilẹ̀-èdè Gẹ̀ẹ̀sì, àwa sì má nlọ sibẹ̀ bí i ẹ̀mejì ni ààrin ọdun. Alẹ́ ọjọ́ Jimọ̀ ni, mo si gbọdọ́ fún ni ìdàhùn ni òwúrọ̀ ọjọ́ Mọnde, ti n se ọjọ́ Ajé ohun ti mo ba fẹ́ se. Mo wa pinnu kin kú ma ro nkan mi lọ́wọ́

bayìí fún ìgbà diẹ mo pinnu lati gbe Drenda lọ sí ibudó ìgbàfẹ́ ni alẹ́ ọjọ nà. Bi mo ti dúró ni orí ìlà, mo ti gbe ọkàn mi kúrò nípa nkan ti mo ni lati se ni òwúrọ̀ ọjọ́ Monde, Lojiji, ni mo mọ ohun ti ó yẹ́ kin se, Ó yé mi kedere bi ojú ọjọ ni. Ẹ̀mi Mimọ́ bami sọ̀rọ̀,, mo si wa dúró si ibi ile íse ti mo wà tẹ́lẹ̀. Laipẹ́ ni awọn ile iṣẹ́ tuntun yìí kógba wọlé ti ko ju bi osù melo lọ.

Kọ́kọ́rọ́ àseyọrí ni—àdúrà; Kí o si ma gbàdrúà ninú Ẹ̀mi nigbogbo igbà kí gbogbo nkan ba le máa lọ dédé pẹ̀lú rẹ wà si le se ìpinnu ti ó tọ́, ati mọ ìlanà ètè fún ohun ìjìnlẹ̀ ti o nilò lati fi borí.

"*Gbàdúrà ní àìsinmi"* (1 Tessalóníkà 5:17.)

ORÍ KEJE

# ÀPÒ ÌSÚRA

Mo ránti ọjọ́ ti mo kọ́kọ́ pàde Dan. O dúrò si ẹ̀yìn ninu ìjọ, ni ibi ìla tógbẹ̀yìn, pẹ̀lú ọmọ ẹ̀gbọ́n mi ti njẹ́ Jẹ̀nnifer. Mo mọ̀ lẹ́yìn ọ̀ rẹyìn pé wọ́n fẹ́ fẹ́ ara wọn ni. Sibẹ̀sibẹ̀, mo le sọ nípa idúró Dan wipe okan rẹ̀ kò si nibiti ó dúró sí. Kóda, ó dà bi wípé ara rẹ̀ kò balẹ̀ rárá. Mo wa gbọ́ wipé ìjọ tiwa yàtọ́ si ìjọ ti ó nlọ. Súgbọ́n bi o ti gbọ́ ti wọ́n bẹ̀rẹ̀ si ni sọ nipá Ìjọba, ó bẹ̀rẹ̀ si ni farabalẹ̀ díẹdiẹ, Òun àti ọmọ ẹ̀gbọ́n mi sì padà wá fẹ ara wọn.

Ni àsìkò na, Dan ndáko lórí ẹgbàáje sarè ilẹ̀ oko ni ààrin gbùngbùn Ohio, nkan kò si lọ dédé fún un. Kodà, kò jèrè ninú iṣẹ́ rẹ ó sì nbàá lọkànjẹ́, sùgbọ́n bi o ti ngbọ́ ọ̀rọ̀ nipa ìjọba síwájú sí i àti bi Ẹ̀mi Mimọ́ ti se le ràn ọ lọ́wọ́, ó wa sí ọ̀dọ̀ Jennifer ní ọjọ́ kan ó ní “Mo fẹ́ sọ fifúnni wa di ilọpó mejì" Ẹnu si ya Jennifer, sibẹ̀ inú rẹ dùn. Nkan ti wọn si se nìyìí.

Ni ọdun nà, ohun ti wọn rí ni orí ilẹ̀ ọkọ wọn yìí kan nà ẹgbàaje saare ilẹ̀ ọkọ si jẹ́ 128% ti ó ga ju awọn ọdun ti tẹ́lẹ̀ lọ. Ó pọ̀ púpọ̀ ju ti tẹ́lẹ̀lọ, tó fi jẹ́ pé wọ́n si le san owò fún ọkọ̀ titun àti ilẹ̀ oko miràn ti wọ́n tún rà,ti o túmọ́ si pé wọn ti ni ilẹ̀ oko tó pọ̀ si ni ọdun ti o tẹ̀ le. Inú Dan dún gàn ni. Ówá sọ pé, Ọdun mẹwa ni wọn ó bá fi san owó ilẹ̀ oko titun nà, ti o sì ti san owó nà bayìí. Mo wa bi Dan leerè pé bawo ni o ti se sẹlẹ̀ mo fẹ́ gbọ́ ìtàn nà.

Ó wá dàbí ìgbà ti Dan àti Jennifer wa béré si ni san ìlọ́po mejì ìfifúnni wọn, wọ́n tun ngbàdúrà pé kí Ọlọrun fi ohun ti wọn o se hàn wọ́n. Dan ni ní ọjọ́ kan bi oun ti nka meeli ti wọ́n sábà má nfi rànsẹ sí òun ni ojojúmọ, ọ̀pọ̀ rẹ ni nipa ọjà tita àwọn àgbẹ̀ ni, òun ti sọ káàdì kekeré yìí sinú ìgbà idalẹ̀nù kí oun tó tún padà lati lọ mú u. Kò si ohun kan pàtàkì ni ara káàdì kekeré nà, ju ìpolówò ilẹ̀ oko àti àwọn ohun èlò fún oko dídá lọ. Wọn fi

iwe nà pe àwọn àgbẹ̀ si ibi ìpade àpérò lati jíròrò lórí àwọn ìrinṣẹ́ oko didá

Dan ni oún rí pé ó yẹ́ ki òun lọ́, lẹ̀yìn ti ó lọ si ìpàdé nà, ó ra àwọn ohun èlò ìrinṣẹ́ tí wọn ti npolówó rẹ̀. Awọn ohunèló irinṣẹ́ na jẹ́ àwọn irinṣẹ́ tuntun ni ọjà fún gbingbin àwọn ti o ni se pẹ̀lú fifúnrúgbin èso àti sísetò ilẹ̀ fún nkan ọgbin tàbí oko dídá. Dan si gbìyànju lati sàlàyé fún mi àwọn idi níti ìmọ̀ sayẹnsi idi ti ó fi mu kí àwọn ohun ọ̀gbin má pọ̀si, sùgbọ́n nise ni mo sọnu ni ìdaji ọ̀nà ninú àwọn àlàyé rẹ̀. Súgbọ́n o yé òun dáadáa, nkan ti o sìse pàtàkì niyìí. Dan sọ fún mi pé òun ni àgbẹ̀ kejì ti yóò rà irinṣẹ́ yìí ni Ohio ni àkókò nà. Ò dára, irinṣẹ́ kekeré yìí ni o dá ọgbọ́n ti o mú irú èsì àbájade tí se ìdá méjìdinláádóje pípọ̀ bayìí wá. Dan tun wa lọ ra ilẹ̀ púpọ̀ si, lonìí, ó ndáko ni orí ẹgbẹ́rún lẹgbẹ́rún saarè ilẹ̀ oko. Ó wá ti ni ọ̀pọ̀lọpọ̀ àwọn ìtàn bi Ẹ̀mi Mimọ́ ti see ràn an lọ́wọ́ lati se ìpìnnu ti o mú yára ju bi ó ti lerò lọ.

Nibayìí báwo ni Dan ti se yí ipòtí kò dára ti oko rẹ̀ ti wà sìi èyítí ó nmú èrè wá báyìí? Ó ntẹ̀lẹ́ Olúdámọ̀ràn, ìmọ̀ràn ti Ẹ̀mi Mimọ́. Nkan ti o ba ni lọ́kàn jẹ́ ni pé, Ọ̀pọ̀ Kristiani ni o ngbọ́ ìtàn na wọn ò si mọ́ bí ó ti se sẹlẹ̀, idi ti mo fi rò pé ó se pàtàkì lati kọ ìwe yìí niyìí. Rárá, Ọ̀pọ̀ kristiani ni yóò ma se àjọyọ̀ bi Ọlọrun ti se tobí tó, wọn mọ̀ pé nkan ti Ọlọeun , úgbọ́n wọn ò mọ̀ bi wọn ti se le sẹdà rẹ̀. Awá ri wipé ọ̀pọ̀ Kristiani ni o kún fún ìtanra-ẹni jẹ́ pẹ̀lú Ọlọrun ti wọn si ndá Ọlọrun lẹ́ fún awọn ìsòro wọn. " Nibo ni Ọlọrun wà? Èmi ò mọ idi ti Ọlọrun kò se rànmilọ́wọ́" Jẹ́ ohun ti mó ma gbọ́ ní ọ̀pọ̀ ìgbà.

Mo lérò pé o ti mọ̀ bayìí, sùgbọ́n nípa òfin ni Ìjọba bá nsiṣẹ́, kì íse, nipa ojúrere. Ọlọrun kò yan àwọn kan ti Òn yóò bùkún fún àti àwọn ti kò ni bùkún. Dan kòsi ninú àwọn ti Ọlọrun dá yàn bẹ́ẹ̀ni kò sì se pàtàkí sí Ọlọrun ju ìwọ na lọ. Ìwọ na ni ẹ̀tọ́ kannà lábẹ́ òfin bi ti Dan ti se ninú ìjọba. Gẹ́gẹ́ bi ẹnikẹ́ni ti ni ẹ̀tọ́ lati gbin irúgbìn ki o si dàgbà so èso, Ìjọba Ọlọrun yóò siṣẹ́ fún ẹnikẹ́ni tí ó bá mọ́ bi a ti se le lo àwọn òfin ti Ìjọba Ọlọrun. Ọ̀kan lára ẹbi ilé Ọlọrun ni o jẹ́ ati ọmọ olú ilú nla ti Ìjọba Rẹ̀ o si ni ètọ́ si ohun gbogbo ti ó ni.

**Torínà jẹ́ kín nsọ fún ọ ìdí tí ọ̀pọ̀lọ̀pọ̀ nínú àwọn ènìyàn Ọlọrun fi nkùnà nínú ayé. Wọn kò mọ̀ bí Ìjọba Ọlọrun ti nsiṣẹ́, wọn kò sì mọ̀ bí wọn ti se le máa gbọ́ Ẹ̀mí Mímọ́.**

> *"Báyìí ni Oluwa wí, Olùràpadà rẹ, Ẹni Mímọ́ Ísraẹ́lì" Èmi* ***ni*** *Oluwa Ọlọrun Rẹ,* ***Tí ó kọ́ ọ fún èrè****, ẹniti* ***ó tọ́ ọ*** *ní ọ̀nà* ***tí ìwọ*** *ìbá má a lọ''*
>
> —Àìsáyà 48:17, NKJV

Àseyọrí Dan kin se nkan ti Dan ti rò tì. Ìlanà ètè ti Ẹ̀mi Mimọ́ ni ti o ti setò sílẹ̀ kí Dan gàn to gbé ìgbésẹ̀ lati lo òfin ti Ìjọba Ọlọrun, Òun àti ìyàwó rẹ̀ ntẹ́tí silẹ̀ si Ẹ̀mi Mimọ áti sọ̀rọ̀ àti rànwọ́n lọ́wọ́ pẹ̀lú èrò kan. Mo fẹ́ ki o kọ nkan yìí sílẹ̀.

## ÈMI MÍMỌ́ NI ÈTÒ!

**Kò sí ohun tó tún lágbara ju kí o ní ètò. Láisi ètò kan àlá ni àwóramn nà, sùgbọ́n pẹ̀lú ètò kan a le kọ́ àlá nà.**

Ẹbí kan le máa fojúinú wòó lati ni ile nla, ti ó ni ọ̀pọ̀lọpọ̀ àwọn yàrá, ibi ìjoko gbàlejò nla ti ó ni àyè, ile ìdáná tigbàlódé, àti ohun elò ilé tó dára tó rẹwà. Sùgbọ́n ni àkókò yìí kì íse nkan miràn tó ju àlá lọ, àwòrán ni. Àwa gbọdọ̀ ya àwòrán nà jade ki à si kọ́ sójú ìwe, àwọn èrò wa. Niwọn ìgbà ti abánikọ́lé ti ni ìwe ti a tẹ̀ jade lọ́wọ́, a le kọ̀ ilé nà. Fún àawọn idí kan, ọ̀pọ̀ àwọn Kristiani ni wọn ní nkan ti mo pè ni ọ̀pọ̀lọ̀/làákáyè ti àpòtí ikówe sí. Ti wọn ba ti gbàdúrà ti wọ́n ti bèrè owó ti wọ́n nìlò, bi Dan ti se, wọ́n ó ma retí ki o kàn farahàn ninú àpòtí ìkòwe sí wọn tàbi kí wọn máa retí kí ẹnikan wa fún wọn. Wọn kò mọ ìlànà rẹ̀ tó kàn.

Bẹ́ẹ̀ni, àkọ́kọ́, o ti mọ àwòrán. Sùgbọ́n àwọn ìlànà wa lati mú ki àwòrán nà di tòọ́tọ́ nibiti wà ti gbadùn rẹ̀. Ìdáhùn ni ètò kan tàbi àwọn ìlànà ètè ti ó nilò lati mú ki o sẹ. Jẹ́ kí nfún ọ ní àpẹẹrẹ. Ti mó ba sọ fún ọ pé mo le yanjú gbogbo ìsòro tí o ní lòrí ọ̀rọ̀ èto-ìsúná rẹ ni kiá kíá ki o lọ mú ìwe àjákọ́ àri bírò rẹ bi mo ti fẹ́ ma sọ àwọn ohun ti wà á nilò lati se, wà lọ mu ìwe àti bírò jade àti setán lati gbọ ìdahùn ti mọ ni. Máa tún sọ fún àwọn ti o nka ìwe yí, nkan tí mo fẹ́ sọ yìí se ése ki ó yọ wàhálà/ áápọn kúrò ninú èto ìsúna rẹ àtí bàkàànnà kí ó yọ ọ́ kúrò ninú oko gbèsè ki ọdun yìí to parí. Nisisiyìí di bírò rẹ mú dáadáa, ki o sì rí dájú pé o kò tà sé kankan ninú àwọn ohun ti mọ bá sọ.

Ìdáhùn nà rọrùn púpọ̀, Máa se àlàyé. Kan lọ jèrè millíọnù mẹ́wa

dọlla ninú ọdún yìí. Wà rọra wo ojú mi fún ìgbà diẹ wa tún máa rọra rẹrín músẹ́músẹ́. Mo wá rò pé ohun ti ẹ̀rín rẹ nsọ ni pé míllíọ̀nù mẹ́wa dọlla kò le tó ọ, torínà, ni mo se fi kún, "Ó dáa, ti ìyẹn kò ba tó, jẹ́ kí a fi se milliọnù mẹẹ́dọ́gbọ̀n dọllà". Èyí kò ni mú ọ rẹ́rín músẹ́ nikan bikose kí o pariwo sókè rẹ́rin. Kílódé? Já ki nsọ fún ọ nkan tó sẹlẹ̀. Fún àwọn ènìyàn kan milliọnù mẹ́wa dọlla le tú wọn silẹ̀ kúrò ninú ìgbèkùn gbèsè, sugbọ́n ẹ̀rín ti wọ́n nrín ni wipé wọ́n kò le rí ara wọn pé wọn le rí irú milliọnù mẹ́wa dọlla ninú ọ̀dún kan. Ti milliọnù mẹ́ẹ̀dọgbọ̀n ni o wá pa wọn lẹ́rín jù nitorí ó jìnnà sí ìwòye ohun tí wọn lerò pé ó seése.

Ẹ jẹ́ kí á wòó pé mo jẹ́ ile iṣẹ́ kan ni òkèèrè lówó, mo wa ni ma san ẹgbẹ̀rúnkan pọ́ùn fún ẹyọ bọ́ọlù kan tí ó bá sọ sínú àpótí sọwọ́ si mi. Jẹ́ ki a wá wòó pé ọ le se bi ọ̀rùndínlẹ́gbẹ̀ta àwọn àpòtí yìí ni ojúmọ́, mo tún wa fi se àdehùn osù méjilá ni iyé owó yi kanna. Èyí tóbi gan, o ju kí a bù mọ nkan lọ fún ìdí àpejúwe yìí, sugbọ́n yóò se àlàyé ohun ti mo fẹ́ lati sọ.

Nibayìí, fojúinú wò pé o ti se ìwe àdéhùn nà mo si sọ gbolóhùn ti mo ti sọ́ sáájú, pé ìdáhùn ètò ìsúná rẹ náà ni èrè milliọnù mẹ́wa dọlla ni àrin ọdún kan ti ó nbọ́, kínni yóò jẹ́ ìdahun rẹ̀? Níbáyìí a kò ni yọ́ ẹ̀rínrín mọ a o pariwo ayọ̀ ni fún ìdùnnú. Kílódé? Nitori lati rí milliọnù mẹ́wa dọlla pẹ̀lú adéhùn nà yóò rọrùn. Kòda, lati jèrè milliọ́nù mẹ́ẹ̀dọ́gbọ̀n dọlla pẹ̀lú yóò rọrùn, àti ti ọgọ́rún milliọnù dọlla nàà yóò seése. Irú ìyípadà nlá wo nìyìí? Ohunkan ti ó ni lati se... ni kí o ti nì ètò. Bi ohun ti mo ti sọ níbẹ̀rẹ̀, pé ẹnikẹ́ni ni o le pa ẹja tí Jesu bati fi hàn wọn ibiti àti báwò ni o ti se le pẹja, torínà, àkókò nà niyìí fún ọ. Nigbàti ó ba ti ni ètò, èto tí ìwọ náà rí ara rẹ pé o le seé, ìsòro ti yanjú, ọ̀nà abáyọ ti wà.

**JẸ́ KÍ NSỌ́ LẸ́Ẹ̀KANSI—MO LÉRÒ PÉ O NÍ LÁTI GBỌ́ Ọ LẸ́Ẹ̀KANSI—ỌLỌRUN NÁÀ NI ÈTÒ <u>RẸ</u>!**

"*Nítorí èmí mọ èrò tí mo nrò si yín ni Oluwa wí, àní èrò àlááfià, ki íse fún ibi, láti fún yín ní ìgbà ìkẹhìn àti ìrètí"* (Jeremaya 29:11

Jẹ́kí ntún sọ lẹ́ẹ̀kansíi -Mo lerò pé o yẹ kí o gbọ́ lẹ́ẹ̀kansìí—pé Ọlọrun ni ètò **<u>RẸ</u>!**

Ní bi osù mélòó sẹ́yìn mo ni aàfàni lati pàde ọkan ninú àwọn

alábásisẹ̀ẹ́pọ̀ ti a jọ wà ninú ìjọ nibití mo ti nkọ́ wọn lẹ́kọ́. Wọn wá lati bèrè ìbérè kan lẹ́yìn ìsìn, tàbi kin sọ pè̩ gbolohùn kan.''Kò sisẹ́! Mo fúnrúgbin èso mi, ènì àti ọkọ mi sàdehùn nípa gbigba akọmàluati eliki/agbọnrín nla, mi ò sí rí ọkankan. Ó sọ fún mi bi o ti so èso fún ìrú eliki ti ó fẹ́ nipàtó, ati akọmalu. . Mo wa bií ní àwọn ìbérè tó pọ̀, mo wa bi pé se lati ìgbà ti ò ti nlọ sóko ọdẹ se o sèèsì ba eliki pade rí. Óni bẹ́ẹ̀ ni, irú èyítí mo fi irúgbìn mi sọ gàn ni mo ri ti o dúró ni ọ̀kánkán mi lọhun ti jìnà fún mi lati yìnbọn fún.''

Nibiyìí, o jami layà diẹ, mo wa bèrè pé kin ni ó wa tún sẹlẹ̀. Óni mo yìnbọn nà dáadáa, sugbọ̀n ọ̀rẹ́ mi ni mo ni kí ó ba mi,yẹ ibọn mi wò, ti o ba se pe ọ̀rẹ́ mi ba mi se ni, on náà kò yẹ ibọn na wò fún ara rẹ̀, torinà ó pàdánù rẹ̀. Bayìí , nitèmi o hàn, sugbọ́n o yanilẹnu, sugbọ́n ki íse fún un.

Mo wòye pé ibiti ọ̀pọ̀ awọn onigbagbọ́ wà. fún àwọn ìdí kan , wọn kò ni òye àwọn ìlànà, ipa ti wọn gbọ́dọ́ kò ninú ìkórè nà. Mo wa ni lati se àlàyé fún un pé Ọlọrun ti se ipa ti Rẹ̀, sugbọ́n on pàdanù ipa tirẹ̀. Se ó ríi Ọlọrun le fún ọ ni ètò, sùgbọ́n o ni lati kó ipa tìrẹ ninú ètò nà ki o ba le sisẹ́. Ìwọ àti Ọlọrun ni!

> *Ìjọba ọ̀run sì dàbí ìsúra tí a fi* ***PAMỌ́*** *sínú oko. Nígbàtí ọkùnrin kan ri i, tí ó paá mọ́ nítórmii ayọ̀ rẹ̀, ó lọ, ó sì ta gbogbo ohun ti ó ní, ó sì ra oko na''*
>
> —Máátiù 13:44

Ọ̀pọ̀lọpọ̀ otítọ́ nipa ìjọba ọ̀run ni o wà ninú ẹsẹ Bibeli yìí, àkọ́kọ́ nà, ẹ̀ jẹ́kí à lọ́ wo ìtumọ ìsúra. gẹ́gẹ́ bi atúmọ̀ èdè ti sọ, ìsúra jẹ́ ohun tóniye-lórí, tó se iyebíye ohun iní iru rẹ̀. Torinà, ohun ìsúra kò ní lati jẹ́ wúrà nikan; o le jẹ́ ohun kohun ti o le nilò ni akókò kan. Ìwe mimọ́ wa sọ pé Ìjọba ọ̀run dabi ìsúrà, tàbi o le sọ pé ohun gbogbo tí o nilò ni ayé ni o wà ninú ìjọban à.Níbo wá ni ìjọba nà wà? Ninú ẹsẹ Bibeli yìí, Jesu sọ pé a fi pamọ́ sinú oko. Wow, se o ni fẹ́ mọ ibiti oko na wà? ó dáa, ìròyìn ayọ̀ nà ni pé Jesu sọ fún wa ibi tí oko na wà àti bakannà bí a ti se le rí ìsúra ti à fi pamọ̀ nà.

Ti à ba lọ wo òwe afúnrúgbìn ninú ìwe Maaku orí Kẹẹrin, a rí ibiti Jesu ti nkọni lórí bi ìgbàgbọ́ ti se le wá ninú ọkan ènìyàn. Nibiyìí ó se àpẹẹrẹ fifi ẹ̀mi ènìyàn we ilẹ̀ ati ọ̀rọ̀ Ọlọrun bi ìrúgbìn ti a gbìn sinú ilẹ̀. Ó

lo àpẹẹrẹ yìí kannà, mo fojúinú wò pe ilẹ̀ nà ni o ntọkasí ninú ìwe Mattiu ori kẹtalá ti o ni ìtúmọ̀ kannà, tin se ẹ̀mi ènìyàn. Mo fẹ́ lo bi ìsẹ́ju mejì lati ràn ọ letí ohun ti a ti kà ni orí kẹfà, pe bi àtise di àtínbi, ẹ̀mi ènìyàn wa di ọkansoso pẹ̀lú Ẹ̀mi ti ỌLọrun, gbàwá layè lati wọ inú èrò ti Ọlọrun. Torinà ìsúra ti o wà ninú oko kò ni òdiwọ̀n kan si wa rárá, bikose pe o tún wa pẹ̀lú ohungbogbo ti Ọlọrun jẹ́ bi àwa ti jẹ́ ọkansoso pẹ̀lú Rẹ̀ ninú Ẹ̀mi.

> *Sùgbọ́n gẹ́gẹ́ bí a ti kọ́ pé, ohun tí ojú kò rí, àti tí etí kò ti gbọ́, tí kò si wọ ọkàn ènìyàn lọ, ohun wọnnì ti Ọlọrun ti pèsè sílẹ̀ fún àwọn tí o fẹ́ẹ—sùgbọ́n Ọlọrun ti sí wọn payá fún wa nípa Ẹ̀mí rẹ̀. Ẹ̀mí ńwadi ohun gbogbo, àní ohun ìjìnlẹ̀ ti Ọlọrun. Nítorí tani nínú ènìyàn tí ó mọ ohùn ènìyàn tán, bíkòse ẹ̀mí ènìyàn tí ó wà nínú rẹ̀? Bẹ́ẹ̀ni kò sí ẹnìkan tí o mọ ohun Ọlọrunbíkòse Ẹ̀mí Ọlọrun. Sùgbọ́n àwa ti gbà, ki íse ẹ̀mí ti ayé, bíkòse Ẹ̀mí ti íse ti Ọlọrun; kí àwa kí ó le mọ ohun tí a fifún wa ní ọ̀fẹ́ láti ọ̀dọ̀ Ọlọrun wa.* 1
>
> —Kọ́ríntì 2:9-12

Bakannà, 1Kọrinti 2:16 tún fi kún pe, *àwa ní ọkàn ti Kristi!* Jesu fìdí ibití ìsúra yìí wà ninú Luku 17:20-21.

> *"Ìjọba Ọlọrun kì í íwá pẹ̀lú àmì ... sáwòó, ìjọba Ọlọrun mbẹ nínú yín"*
>
> —Luku 17:20-21

> *"Tàbí ẹ̀yin kò mọ̀ pe ara yín ni tẹ́mpílì Ẹ̀mí Mímọ́, tí mbẹ nínú yín tí ẹ̀yin ti gbà lọ́wọ́ Ọlọrun? Ẹ̀yin ki íse ti ara yín: nítori a ti rà yín ni iye kan; Nítoriná ẹ yin Ọlọrun lógo nínú ara yín"*
>
> —1Kọ̀ríntì 6:19-20

Níbayìí, jẹ́ kin sọ ohun ti mo ngbìyànjú lati sọ nísókí.

## ÌSÚRA WÀ NÍNÚ RE!

Báwo ni ó ti pọ̀ tó? Ìsúra ti ó pọ̀lọpọ̀lọpọ̀ ju àlá rẹ lọ? Ìsúra ti kò lódiwọ̀n!

*Ǹjẹ́ ẹnití o le se lọ́pọ̀lọpọ̀ ju gbogbo èyítí a mbèrè tàbí ti a ńrò lọ, gẹ́gẹ́ bi agbára tí nsisẹ́ nínú wa.*

—Efesu 3:20

**Ọ̀RẸ́ MI,TÌRẸ NI GBOGBO RẸ̀, GBOGBO ÌJỌBA . ỌLỌRUN KÒ LE FI OHUNKÓHUN KÚN OHUN TÍ Ó TI FIFÚN Ọ TẸLẸ́ MỌ́.GBOGBO RẸ̀ NI O TI NÍ!**

Nibáyìí, a ni lati kọ ara wa ni ọ̀na ti o tún yàtọ̀. Ìsúra yìí ju ohun tí a le ní lérò lọ! Ní déede igbà, tí a ba nilò ohunkan tàbí ìrànlọ́wọ́, àti kọ́ ara wà lati ma wo òde ara wa fún ìdáhùn /èsì. Sùgbọ́n nibáyìí, Ẹ̀mi Mimọ́, Ọlọrun tìkararẹ̀, ngbé inú wa Òun sì ni ìrànlọ́wọ̀ wa. A ti jíróró lórí bi a ti se le máa gbàdúrà ninú Ẹ̀mi tàbi ní fífièdèfọ̀ ti o mú ìtọ̀ni àti fi àwọn ohun ijìnlẹ̀ han wà. Sùgbọ́n ọ̀pọ̀ ènìyàn ni ó le fún lati mọ̀ bi ìrú ìrànlọ́wọ́ yìí kòse le jẹ́ tàbí jẹ́ ohun ti Ọlọrun fẹ́ ki ó jẹ́ èsì àbájáde ni gbogbo ohun ti se ayé wọ́n.

Sùgbọ́n bí o bá ti di àtúnbi, ó ti di ẹbí ni ìdílé ti Ọlọrun àti ọmọ ìjọba nla Rẹ̀. Nitori ó ti fún yin ní ohun gbogbo tí ó ni! Luku 12:32, sọ pé kò sí ìdí lati bẹ̀rù tàbi máa ni ìpayà nitorí didùn inú Baba yín ni lati fi ìjọba fún yín. Ìjọba wo? Ìjọba Rẹ̀!

*"Má bẹ̀rù agbo kékeré; nítorí dídùn inú Baba yín ni lati fi ìjọba fún yín"* (Luku 12:32)

Tiyín ni gbogbo rẹ̀, Ọ̀rẹ́ mi, àní gbogbo ìjọba. Ọlọrun kò tún ni fi ohunkohun kún gbogbo ohun tó ti fifún yin tẹ́lẹ̀. Torí o ti ni gbogbo rẹ̀! Ọ̀pọ̀lọpọ̀ àwọ̀n ènìyàn ni wọn má nro wipé àwọn nda Ọlọrun láàmú ni, nígbati àwọn bà jẹ́ kí Ọlọrun dásí ọ̀rọ̀ ayé àwọn. Sùgbọ́n àìmọ̀kan pọ́ nbélé ni. Ti mo ba sọ fún ọ pé ọmọ orilẹ̀-èdè Gẹ̀ẹ́sì ni ọ, ti o wá sọ pé, "Ó dáa, mi o ti ẹ̀ mọ̀. Ti mo bá ni sọ́ọ́bù nibiyìí, má a má bẹ̀rù, ma tún máa dá ẹnìkan láàmú ti mo bá fẹ̀ lo anfàní òfin ti orilẹ̀-èdè ti o le gbà mi láayè lati bẹ̀rẹ̀ oko-òwò mi nibiyìí" Gẹ́gẹ́ bí ọmọ orilẹ̀-èdè, o ti ní ẹ̀tọ́ ati gbogbo àwọn ànfàni ti ọrilẹ̀ -èdè ní fún ọ. Tìrẹ ni gbogbo rẹ̀! Má dúró ṣẹ́yìn. Gba gbogbo ẹ̀tọ́ àti àwọn ànfàní ti ó jẹ́ tìrẹ!

**Kílódé tí a se ńfi ìjọba ọ̀run wé ìsúra?**

Nitorí ti o ba ti ni ànfaní si ìmọ̀ ti ọ̀run, wa ti le mọ ohun tí wà se ninú gbogbo ipòkìpo pẹ̀lú ìlànà ète ti Ọ̀lọ̀run ti kò wọ̀pọ̀. Jẹ́ ki nfún ọ ni àpẹẹrẹ miràn bi o ti se nsiṣẹ́.

Nìgbàti èmi àti Drenda béré lati máa kọ́ nipa ìjọba, ayé wá yípadà pàtàpàtà lọ̀nà ti ó yanilẹnu. Bi a ti yọ kúrò ninú ogun gbèsè jẹ́ ìtúsilẹ̀ nla ni, àyé wà gba àtúnse tó ládùn. ìyàlẹnu nla ni bi a ti se san owó saarè ilẹ̀ máárùndínọ́gọ́ta àti bí inú wà se dùn tó pé a ti fẹ́ jade kúrò nínú aheré wa. Ìyàlẹnu, sibẹ̀ a tún nilò ile lórí ilẹ̀ na. a kò tilẹ̀ mọ ohunkóhun lórí ànkọ́lé, bẹ́ẹ̀ sì ni a kò mọ ibi ti a ó ti bẹ̀rẹ̀. Sùgbọ́n a bẹ̀rẹ̀ sí ni gbàdúrà nipa BÁWO ni a ti se rí ilé tí a fẹ́ kọ. A ni lati gbẹ́kẹ̀lé Ẹ̀mi Mimọ́ ti yóò ràn wá lọwọ́.

Kí a má ba jẹ́ gbèsè mọ rárá, a béré si ni wa ọ̀nà bi a ti se le kọ́ ilé nà. Ọ̀nà kan ti ó jẹ́ ki a ni ile nla yìí pẹ̀lú owó ti kòpọ̀ ni pé a sé ni ọna ti ó gbà rọrùn. Ilé na kí íse bi ọkọ àkẹ́rù nla, sùgbọ́n ọ jẹ́ ile ti a rọra tò sorí ilẹ̀ wa ni apá kan ti ìlé iṣẹ́. Ilé na si dára bi ti bi awọn ile ti ànkọ́ ni, sùgbọ́n ní ẹ̀dínwó nitorí ọ̀na ti a gbà kọ́ ile nà. Awá lọ se àkiyèsi àwọn ile iṣẹ́ mẹta kan ti a kọ ni ọ̀nà yìí bákanna lati wo nkan ti wọn nse. Lẹ̀yìn na ti a ti wádi àti rí ohun ti wọn nse, àwa na wa ròó pé ọ̀na ti àwa ná yóò fẹ́ lati tọ̀ ni lati se àwokọ́se ọkan ninú wọn ti yóò fún àwa na ni ànfani nlá lati ni ile nla lorí ilẹ̀ tiwa náà. A gbà lati fọwọ́si ìwe àdehún lẹ́yìn ti a padà délé lati ileẹ̀kọ́ ti wọn pè wá si lati wa bá wọn sọ̀rọ̀ ni Virginia. A pinnu lati gbe àwọn èrò ti wa àti jíròrò lórí gbogbo rẹ̀ lorí ohun ti a kò ti se àti mọ̀ dájú pe à mọ ohun ti a fẹ̀ ki a tó lọ tọ́wọ́bọ ìwe àdehùn nigbàti abápadàdé.

Mi ó niran bi o ti se wáyé mọ́ ohun ti ó mú kí wọ́n pè wa si ibi ìpàde ti o wáyé ni Virginia, sùgbọ́n a fiwé pè wá lati wá dúró pẹ̀lú wọn ni ilé ẹ̀kọ́ nà. Bi a ti dé ile ti o rẹwà na lati padé àwọn ọ̀rẹ́ wa tuntun, a ti nsọ fún wọn bi ilé nà ti rí. Ò yà mi lẹnu bi mó ti de ibẹ̀ fún ìgbà àkọ́kọ́," "Sé alagbase ni ẹ̀yin èniyàn wọ̀nyí ni" Ni mo bèrè, Rárá" ni wọ́n sọ. Baba ni onísirò -owó ni òun ni ile iṣẹ́ nla kan. Ó dáa, bawo wa ni ẹ tise mọ̀ bi à ti se nkọ́le?" Ni mo bèrè.

Wọn sì bẹ̀rẹ̀ si ní sọ orísírísí àwọn nkan, àti pé ninú àwọn ọ̀rọ̀ wọ̀nyìí, à sọ fún wọ́n pé àwa nà nkọlé pé ti a bá ti delé ni a ọ lọ fọwọ́sí ìwe adehùn. Inú wọn dùn lati gbọ́ wọn si bẹ̀rẹ̀ sí ní bi wá nipa ilé titun nà. Awá bẹ̀rẹ̀ si ni sọ nipa ìjọba bi o ti se yí ayé wa padà. A tún pín pẹ̀lú wọn bi a ti se ra saarè ilẹ̀ marùnlélàádọ́ta ati bi inú wa se dùn to lati Jade kúrò ninú ahere.

A sọ fún wọn pé ètò rẹ̀ wa lọ́wọ́ wa, wọn ni se àwọn le rí wọn, ti o si jẹ́ pé inú ti wa nà dùn lati fi fún wọn fún àfikún. Amú ìwe ètò na jade à si joko ni ibi tábìlì ti ile ìdána wọn ti a sit ẹẹ le lorí. Kò ti lẹ̀ pẹ́ tí ìyawó rẹ̀ fi nsọ́rọ̀ bayi pé, rárá, o, "ayè tó wà yí ti kéré jù" tàbi “se o fẹ́ ilé ìdáná nla," tàbi “se o ti ròó wò pé bí àwọn ọmọ rẹ se ndágbà? Gẹ́gẹ́ bi Pasitọ, ẹ nílò ibiti ó tóbi gan fún gbigba àwọn àlejò" Kókó ibẹ̀ nipé wọn wa fi hàn wá idi ti kò fi yẹ pé ìrú ile nà ni a kí á kọ, a si ni lati gbà pẹ̀lú wọn ni ohun gbogbo ti wọn só. Ó dáa, báwo ni a ti se fẹ́ kọ́ ilé nla pẹ̀lú ìwọnba owó ti a fẹ́ ná? “Ìyẹn rọrùn, ni wọn sọ. “Kọ́ fúnrarẹ" Nigbatí mo gbọ àwọn ọ̀rọ̀ wọ̀nyií, Mo fẹ́ rẹ́rin. Èmi kọ̀ ilé ara mi?" Bi mó ti sọ pé èmi kò mọ nkankan nipa ilé kíkọ́! Bẹ́ẹ̀ ni bẹ̀rẹ̀ sí ní gbà wá niyànjú, wọn ní kì íse ohun tí ó le ni. Wọn wa sọ fún wa nipa ìwe kan ti wọn npé, Ri pé o fí tó *ọ̀kẹ́méjì àbọ̀ pọ̀ùn sí ìpamọ́ tàbí jù bẹ lọ bí alàgbàse gbogbogbo: Bí o ti se le sètò rẹ̀, pín isẹ́ fún àwọn alágbàse míràn kí o sì kọ́ ilé tí ó ni lọ́kàn láti kọ́* Warren V. Jaeger sọ.

Nígbàti a padà dé ilé, a kò lọ́ fọwọ́ si ìwe àdehùn ti irú ile tí a ni a fẹ́ kọ́ tẹ́lẹ̀ mọ́. A lọ ra ìwe tí wọn sọ lati kàá, mo sì nronú bi mo ti se nka orí ekínní ìwe nà. A sì bẹ̀rẹ̀ si ni fojú wo àwọn ile ti ó jojúnigbèsè míràn bakanna. Lopin rẹ̀, a rí ile kan ti àwa na ni fẹ́ si à si bẹ̀rẹ̀ si ni se àtúpalẹ̀ bi a o ti sé ni silẹ̀tẹ̀lẹ́. A ba àwọn ọ̀rẹ́ wa sọ̀rọ̀ àti àwọn ènìyàn ti a rí pé wọn ti kọ́ irú àwọn ile yìí pẹ̀lú. Nipárí, à pinnu pé àwa nà le kọ́ irú rẹ̀! A wá wó àwọrán ile na a wá bi ara wa léèrè, pé kín ni ohun tí àwa nà lè se lati lè kọ́ ilé ti a ni a fẹ́ yìí?" Sí ìyàlẹ́nú, mo pinnú lati fa okùn iná si gbogbo ilé, bíótilẹ̀jẹ́pé mi o tilẹ̀ fi ọwọ́ kan fánrán wáya ina ti nse ìwọ̀n ìpín mejìlá si meji ni ayé mi. Ọ̀rẹ́ mi kan tí ó mọ̀ nipa bi a ti nfa ina sinú ilé sọ fún mi pé nkan ti o rọrún ni òun yóò si fi hàn mí bí ma ti sé.

Nitorí isẹ́ témi ni mò nse, Drenda náà ni òun yóò ma sisẹ́ pẹ̀lú àwọn agbanisíṣẹ́ ti wọn nsisẹ́ kọ́lékọ́lé. A pe àwọn oniṣẹ́ gbogbo kalẹ̀ lati le yàwòrán ilé nà, ọwọ́ wa ni ohun tó kù kù sí. Àwọn ohun ti ó ti o tún kù lágbára sùgbọ́n o jẹ́ àwọn ọjọ́ ti ó wúnilóri ninú ayé wa. Lati gẹ̀ ni kúkúrú, ki a má fọ̀rọ̀ gùn, a kọ ile nà parí, pẹ̀lú ìlọ́po mejì ìwọ̀n ẹṣẹ̀ onihamẹ̀rin àwọrán ile kíkọ́. A ni lẹ̀kùn onigí tí o dúrò dáa; wọ́n wọ́ gbogbo ilẹ̀ ilé na pẹ̀lú àwọn igilile àwọn igi ti ó lágbára ni wọ́n fi deladé; ti wọn seé tó rẹwà gan, ohun ọsọ ilé ti wọ́n lò ni ile ìdánà jẹ́ ti àwọn irin tí kò le dógún. ri

wipé à fi owó tí ó le ni ẹgbẹ̀rúnlọ́gọ́rúnméjì pọun pamọ́ kí a tó le kọ́ ile nà fúnrawa.

**GBOGBO ÌGBÀ NI MO MÁA NSỌ PÉ A FI OHUN ÌJÌNLẸ̀ ỌLỌRUN PAMỌ́ FÚN! KÌ ÍSE LÁTI Ọ̀DỌ̀ RẸẸ́ NINÚ ÒKÙNKÙN NI SATANI NGBÉ KÒ SÌ MỌ ÀWỌN ÈTÒ TI ỌLỌRUN.**

Lónìí, inú mi má ndùn pé à ti bi Ẹ̀mi Mimọ́ lati ràn wá lọ́wọ́ pẹ̀lú àwọn ètò nà. Awọ́n àbajáde èsì náà sì jẹ́ àwọn ohun tí à kò le láàlá pé ohun ti a lè dá se ni. O si tún jọmílójú bí Ọlọrun ti se irin àjò wa lọ si Virgina àti mú wa pàde àwọn tọkọtìyàwó ti wọ́n sẹ̀sẹ̀ parí ile ti wọ́n na. Mo si mọ̀ dajúpé ti kò bá sẹlẹ̀ bẹ́ẹ̀ ni, ilé tí a pinnu lati kọ́ tẹ́lẹ̀ ni a ò ba si kọ́. Ilé àpọ̀jùwọ́n yìí nà ni à ba sì kọ́. Mi ò sọ pé ilé nà kò ni siṣẹ́ ti o yẹ fún ìgbà diẹ̀, sùgbọ́n laipẹ́ ni kò ni gbà wá mọ. Ilé tí à kọ́ yìí sì jẹ́ ẹ̀rí sí mi bí Ẹ̀mi Mimọ́ ti se le ràn ọ́ lọ́wọ́ ninú ipòkípò ti yóò sọ ètò na fún ọ àti tọ́ ọ sọnà kọjá ohun tí o lérò!

Torínà lẹ́ẹ̀kansi, jẹ́ kin sọọ́ lẹ́ẹ̀kansi . . .

**Ọlọrun ní ètò Rẹ!**

Sùgbọ́n o le sọ pé "Gary, gbogbo ohun tí o sọ ni ó dára, sùgbọ́n ìwe Maattiu 13:44 sọ wipe a fi ètò na pamọ̀!" Ati pé ó wà fún ànfàni rẹ ni. Wo ohun ti Jesu sọ ninú ìwe Mattiu 13:10-11.

> *Àwọn ọmọ ẹ̀hìn rẹ̀ si tọ̀ó wá, wọ́n bi pé, Èse tí ìwọ ńfi òwe bá à wọn sọ̀rọ̀?" Ósì dáhùn wí fún wọn pé, **Ẹ̀yin ni a fifún** láti mọ ohun ìjìnlẹ̀ ti ìjọba ọ̀run sùgbọ́n a kò fi fún"*
>
> —Maatiu 13:10-11

Ohun ìmọ̀ ìjinlẹ̀ yìí wà fún ọ ki í se fún èsu tàbi àwọn èniyàn buburú ti wọn le sì í lò, tàbi ti ó le fẹ́ dí ètò ti Ọlọrun lọ́wọ́ lati mọ̀ ọ́. Bibeli sọ pé Satani le yí ète rẹ̀ pada ti ó ba le mọ ohun tì Ọlọrun nse.

> *Sùgbọ́n àwa ńsọ̀rọ̀ ọgbọ́n Ọlọrun ní ìjìnlẹ̀ àní ọgbọ́n ti ó farasin, èyití Ọlọrun ti làna silẹ̀ sáajú ìpìlẹ̀ ayé fún ògo wa. Èyiti ẹnikẹ́ni nínú àwọn olórí ayé kò mọ,nitorí ìbásepé wọ́n ti mọ̀ ọ wọn kì ba tí kan Oluwa ògo mọ́ àgbélebu"*
>
> —1Korinti 2:7-8

Mo máa nfi ìgbà gbogbo sọ wípé ohun ìjìnlẹ̀ Ọlọrun ni à fi pamọ́ fún ọ kì íse láti ọ̀dọ̀ rẹ! Inú òkùnkùn ni Satani ngbé kò sì le mọ ètò ti Ọlọrun . Ó kàn le dásí nikan ni si ohun tí Ọlọrun ban se. Ìgbatí o fi ma mọ ohun tí ó nlọ, ó ti pẹ́ jù fún un. Torinà ni ìgbà míràn ti o bá nbẹ̀rú nitorí tí ilẹ̀ nsú lọ tí o kò si tìí mọ ohun ti wàá se, mo fẹ́ kí o mọ̀ pé Ọlọrun kìí pẹ́ jù, ohun tí o sì le máa rí bi ìdáduro ni ó nsiṣẹ́ fún ọ nipa pípa ìdáhùn rẹ pamọ́ títí yóò fi tó àkókò fún lati fi hàn.

> *Ìjọba ọ̀run sì dàbí ìsúra tí a fi **PAMỌ́** sínú oko. Nígbàtí ọkùnrin kan ri i, **tí ó paá mọ́** nítórmii ayọ̀ rẹ̀, ó lọ, ó sì ta gbogbo ohun ti ó ní, ó sì ra oko na''*
>
> —Máátiù 13:44

A ti jíròrò lórí kínni àti níbo ni ilẹ̀ oko náà wà kín si ni idi tí a fi pa ìsúra náà mọ́ síbẹ̀. A si tún ti sọ̀rọ̀ lórí bi a ti se le gbọ àwọn ohunti a kó pamọ̀ lati ìjọba Ọlọrun nípa gbígbàdúrà ninú Ẹ̀mi àti títẹ́ti lati gbọ́ ohùn ti Ẹ̀mi Mimọ́. Sùgbọ́n ohun mìràn to se pàtàkì kan tún wà ti o gbọdọ̀ mọ̀ ti a kọ sinú ìwe mimọ́. Kì íse nitorí ohun ti a fi pamọ́ ni ó fa ìsubu ọ̀pọ̀ ètò rere ti o dára tí o ní àti fa ìparun tàbi àdánù ninú ayé àwọn èniyàn. Tí o bá se àkíyèsí ninú ìwe mimọ́ ni keté ti èniyàn gbọ́ nipa ìsurà, èrò, ìtọ́ní, tàbi ètò lati ọ̀dọ̀ Ọlọrun, Ó sọ pé ó tún lọ lati fí pamọ́ lẹ́ẹ̀kansi. KÒ GBÉ ÌGBÉSẸ̀ LÓRÍ RẸ̀ lẹ́sẹ̀kẹ́sẹ̀!. Kò lọ máa sọ fún gbogbo àwọn ọ̀rẹ́ tàbi aládúgbò rẹ̀ nipa ohun ti ó gbọ́ lati ọ̀dọ̀ Oluwa tàbi nipa àwọn ètò titun ti ó ni, kò ti yá. Bibeli sọ pé o tun lọ fi pamọ́ lẹ́ẹ̀kansi, ó lọ lati lọ ta àwọn ohun gbogbo tí ó ní, o si wá ra oko náà. Ohun ti ó túmọ̀ si ni wípé, Kò fẹ́ lati fi ibiti ìsúra náà wà han ẹnikẹ́ni titi ilẹ̀ oko nà fi di ẹ̀. Bí o ti se ndúró títí o fi di tirẹ̀, ó mọ̀ dajú pé kò sí ẹnití ó le jì kúrò ni ọwọ́ rẹ̀.

Ìwe mimọ́ tun fi hàn wá pé ni igbà ti ó kọ́kọ́ ríi ìsúra yìí, kò si ní ipò ẹniti o le ri owò fún ilẹ̀ oko ìsúra nà, ó sì ní lati se àwọn nkankan nà kí ó tó le ra ilẹ̀ oko nà. Àwọn ìgbéṣẹ̀ yìí kọja pé mo ni owó mo sì fẹ́ lati ra nkan. Èyí ni ó nkọ wa ni àwọn òfin  to se pàtàkì nipa ayé àti bí o ti gbọdọ̀ gbé ìgbésẹ̀ lorí ohun ti Ẹ̀mi Mimọ́ bá fi hàn ọ́ tí o bá fẹ́ sorire.

Ìwe mimọ́ nsọ pé níkété ti o ba ti gbọ́ ìtọ́ni ati èrò yìí o kò gbọdọ̀ se ohunkóhun tití ìwọ na yóò fi ni agbára lati le gba ilẹ̀ nà. Mo lérò pé

gbogbo wa ni o ti ri bí o ti se nsísẹ pẹ̀lú owó. Tí o kò ba ni owó tó tó lọ́wọ́ lati ra ilẹ̀ nà, ó dájú pé ó kò ní sọ fún ẹnikẹ́ni pé ìsúra wà lorí ilẹ̀ náà. Torí o mọ̀ pé ti ẹnikẹ́ni ba mọ̀ pé ìsúra wà lorí ilẹ̀ náà, ẹlómiràn ni yòó wà rá. Dípò bẹ́, wa lọ lati se ohun yówù tí wá se lati le rí owó ti wàá fir a ilẹ̀ náà, ti wà si pa òtítọ ti o mọ̀ nipa ìsúra nà mọ́ fún ara rẹ.

Ìlànà òfin yìí kanna ni otítọ́ fún gbogbo ìtọ́ni àti ìdarí ti Ọlọrun le fifún ọ. Ni ọ̀pọ̀ ìgbà ni awọn kristiẹni ma sì í gbé lati ìbẹ̀rẹ̀ dé òpin. Ni ọ̀pọ̀lọpọ̀ ìgbà ni Ẹ̀mi Mimọ́ yóò fi àwọn èrò kàn si wa lọkàn, kò fi hàn wa lati lọ gbe ìgbésẹ̀ ni kiakia lórí rẹ̀ ni àkókò na, sùgbọ́n fún wà lati máa gbáradi ki a má ba pàdánu ànfàní ná. ìgbáradì fún ohungbogbo ti a fẹ́ dawọlé jẹ́ ohun ti ó se pàtàkì fún àwọn ilànà. Ninú eré ìdárayá sise lati borí tàbi pàdánu wà lọ́wọ́ àwọn ẹgbẹ́ agbá bọ́ọlù nà bá ti se gbàràdì sí tàbi palẹ̀mọ fún ìdíje nà, nigbàtí ẹnikẹ́ni kò wò wọn. Sùgbọ́n o ni latí gbá pẹ̀lú mi pé ìgbàradi ki ise ohun ẹ̀fẹ̀/yẹ̀yẹ̀; ó wà fún sísakitiyan àti ìgbiyànjú. Fún àkàwé, gbogbo èniyàn ni o fẹ́ràn àriwò ìdùnnú ti èré ìdárayá, ọ̀pọ̀ àwọn èniyàn, imọlẹ̀ àti ayọ́ ti ìségún/ biborí.

Óse ni láànu pé àwọn àlá wọ̀nyìí ma ndi ìrora àti ìbanujẹ̀ nigbàti a kò ba kọbiara sí ìgbaradì/ ìpalẹ̀mọ yìí. Mi o le sọ fún ọ iye àwọn èniyàn ti wọn ti ba ayé ara wọn jẹ́ nitorí tí wọn kò mọ àwọn ìlànà yìí. Mo ti rí ọ̀pọ̀ àwọn ti Ọlọrun pè ni òtítọ́, àwọn ti ati fòrórórò yàn ti wọn jade lọ lati dá ìjọ silẹ̀ nigbati wọn o ti gbáradì silẹ̀ ni tí ìmọ́ara tàbi ni ti ìsúnà wọn ti àjálù si de bá wọ́n, dípò ki àlá wọn wa si ìmúsẹ́, mo ti rí àwọn ti Ọlọrun fi si wọn lọ́kàn irú iṣẹ́ ti wọn le se, ti wọ́n si mọ̀ dajú pé ó máa yọrí si rere, ti wọ́n si fí iṣẹ́ ti wọ́n nse silẹ̀ lati ti palẹ̀mọ tó ti wọ́n sì bá ara wọn ninú gbèsè banki. Ohun ti o wá bani lọkàn jẹ́ ninú gbogbop ìtan yìí ni wipé Ọlọrun nà ni à tún dálẹ́bi, àwọn èniyàn si sọ ara wọn di ẹni yẹpẹrẹ kì íse si ara wọn nikan, bikòse pẹ̀lú Ọlọrun. Ẹ̀mi kò mọ idi ti àwọn èniyàn se máa nrò pé oríire kàn máa nsadéé wá ni. Sùgbọ́n a ni lati dá àwọn èniyàn lẹ̀kọ́ ilànà si àseyọrí àti orìre bí ó ti se wà ninú ìwe Mimọ́.

Àwọn èniyàn máa nwá sọ́dọ̀ mi tí wọn ó sọ fún mi wípé, Háà, Pasítọ, Ọlọrun sọ́ fún àwọn pé ìjọ yìí ni ìjọ mi" Tí a kò sì ní tún rí wọn mọ́. Háa, Pástọ̀ Ọlọrun ni o fi òye iṣẹ́ nla yi fún mi" Nkan ti a ó gbọ́ lẹ́yìn rẹ nipé wọn gbe ilé ti wọn ngbé àti ọkọ̀ wọn tà ni gbànjo. Ohun ti Ọlọrun fẹ́ fún ọ KỌ́ nìyìí.

Nigbati Ẹmi Mimọ́ bá là wá lóyé ohunkan, kò túmọ̀ si pé a gbọdọ̀ bẹ̀rẹ̀ rẹ̀ ni kiakiá. Ọ̀pọ̀ ìgbà, ó fẹ́ ki á fi àlá nà pamọ́, ki a wá bẹ̀rẹ̀ si ni máa palẹ̀mọ/ gbaradi bí a o ti se bẹ̀rẹ̀ rẹ̀. Lóòtọ́, a kò ti ní gbogbo ohun ti a nílò lati le è fi bẹ̀rẹ̀ iṣẹ́ na fún àseyọrí. Gbígbáradi/ ìpalẹ̀mọ́ fún ohun nà le gba ọ̀ṣẹ̀ kan tàbi ọdún kan, ó dá lé orí ohun nà tí Ọlọrun fi hàn ọ́ láti se. Ríi dajú pé ohun ti ò ngbáradì fún yé ọ atipé o seé ni àkókò nà tún se pàtàkì se pàtàkì gàn ju nkan ti o ngbà lérò gan lọ.

Ní tèmi, mo mọ̀ pé a pè mi lati máa wàásù ìhìnrere ni lati ìgbàti mo ti wà ni ẹni ọdun mọ́kàndínlógún. Mo tí ri ara mi nibiti mo ti gbé Bibeli lọ́ wọ́ tí Ọlọrun si sọ pé, “Mo npè ọ́ lati wáàsù ọ̀rọ̀ náà" ni ẹmẹta ni ó sọ ọ́. Ó jẹ́ ìrírí ti ó dájú àti ni agbára ti mó ní. Sùgbọ́n Ọlọrun kò sọ fún mi lati bẹ̀rẹ̀ si má wáàsù ni kiákiá ni àsikò nà. Dipò bẹ́ẹ̀, ó sọ fún mi lati lọ sí ilé ẹ̀kọ́ gbigba. Jẹ́ kí nsọ fún ọ, àpapọ̀ ohun ti mó ba jade ni ilé ìwe mi ni ẹ́.é, ti o sì máa tìmi lójú lati jẹ́ ki nwà láàrin àwọn ti ó wà ni àyíká mi. Bẹ́ẹ̀ni mi o ti dàgbà tó ẹniti ó le má se Pasitọ̀ fún àwọn ènìyàn pẹ̀lú! Torinà mo wagb a ilé ẹ̀kọ́ lọ, ó si le koko nigbànà—sùgbọ́n mo faradàá mo sì parí ẹ̀kọ́ gboyè ni ọdún kẹ́rin.

Bí mo ti jade ni ilé ẹ̀kọ́ nà, mo ntún ròó pé se ó ti tó àsikò lati bẹ̀rẹ̀ si wàásù. Sùgbọ́n Oluwa sọ fún mi pé, óun fẹ́ ki nlọ bẹ̀rẹ̀ iṣẹ́ pẹ̀lú ilé iṣẹ́ ti elétò ìsúna ti nse ìdúró fún ààbò ni àgbègbè. Lóòtọ́ kò nitumọ̀ sí mi, sùgbọ́ n mo mọ̀ pé ohùn Ọlọrun ni mo ngbọ́,mo si lọ lati gba iṣẹ́ nà. Iṣẹ́ na tún wá le ju ìgbàtí mọ wà ni ilé ẹ̀kọ́ lọ. Mo wa ni lati má pé ni ojojúmọ́ àti kọ́ bi ma ti ségun bíbẹ̀rù àwọn èníyàn. Lati ma gbé ayé mi lorí iwọnba iṣẹ́ to ba se ni wàá gba òyà rẹ̀ tun sú mi, kòda ojojúmọ ni ó wùmi lati fi iṣẹ́ nà sílẹ̀, sùgbọ́n mo mọ̀ pé mi ó le se é. Niparí, lẹ́yìn bi ọdún diẹ̀, mo ti wa mọ iṣẹ́ ti mò nse dáadáa. Òtítọ́, èmi àti Drenda ni a mú ìdagbàsóké bá ọfisi àkọ́kọ́ ninú bi ẹgbẹ̀rún márun àwọn ilé iṣẹ́ tí a ti nsiṣẹ́ káàkiri àwọn orilẹ̀-èdè.

Ní akókò yií ni Ọlọrun sọ fún mi pé àsikò niyìí lati lọ́ dá ìjọ silẹ̀. Mo si ti tó ẹni ogojì ọdún ni àkòkò yí. Ó gbà Ọlọrun ni ọdún mọkànlelogun lati pèsè mi sílẹ̀ fún ìran ti ó ti sọ fún mi lati ẹni ọdún mọkàndínlógun. Níkété ti mo bẹ̀rẹ̀ isẹ́ ìrànṣẹ́ mi, mo wá rí àwọn ìdì ti mó fi ni lati gbáradì silẹ̀. Síse isẹ́ ìrànsẹ́ tún lágbára ju bi mo ti lérò pé yóò rí lọ. Sùgbọ́n nitorí mo ti lọ fún ìdánilẹ̀kọ̀ pẹ̀lú àwọn ènìyàn àti ni ìrírí ninú àwọn iṣẹ́ ti mo ti se nipa ti kíkọ̀silẹ̀, mo rí dájú pé mo jẹ́ olótitọ́ si ìpè Ọlọrun ninú ayé mi. Gbogbo

ípè tàbi ìṣẹ́ àkànse kọ́ ni yóò gba ọdún mọkànlélógún kí ó tó gbàràdì tán, sùgbọ́n ọ̀kànnà ni àwọn ìlànà ìgbáradi yóò jẹ́.

Nítorí àwọn ìlànà ti gbigbaradì yìí ma fẹ́ ki a lọ wo Máátiù 13:44:

> *Ìjọba ọ̀run inú rẹ yóò fún ọ ní ìmọ̀ tàbí àyè sí ibi ìmọ̀ ohun ìjìnlẹ̀, tàbí àwọn ohun ìpamọ́ tí Ọlọrun mọ̀. A le rí ìmọ̀ yìí gbà láti ọ̀dọ̀ Ẹ̀mí Ọlọrun, Òun kanna tí ó wà nínú rẹ. Nígbàtí ènìyàn bá ti mọ̀ tàbí gbọ́pé ìmọ̀ ìjìnlẹ̀ yìí ni íse ìsúra fún un, ìdáhùn fun, ó tún wá fi pamọ́ sínú ọkàn rẹ̀. Tí o sì ń fi ayọ̀ se ohun gbogbo tí ó ní ní ipá láti se pẹ̀lú ìgbáradì ní pẹ̀lẹ́pẹ̀lẹ́ láti lépa ní ọ̀nà àti ní ti ìtọni ti Ọlọrun ti fi hàn án láti leè rí ìdáhùn gbà.*

ORÍ KẸJỌ

# IBI ÌGBÉGA TÍ O LE KOKO

Ọ̀rẹ́ mi Pasitọ Peteru àti ìyàwó rẹ̀, Bev, ti wọ́n jẹ́ olùdarí ìjọ nla kan ní New Zealand, ni wọn mbọ̀ wa si ilú Òyinbó US lati se àbẹ̀wò kan ni kíákíá. Àsikò ọdún kérési ni, wọn ni àwọn yóò tẹṣẹ̀ dúró ni ibi kan ti a npé ni Colorado Spring ni ibi ilé ítúra Broadmoor fún bi ọjọ́ mejì lati sinmi àti jẹ ìgbàdùn ọdún kérésìmesì. Tí o kò ba ti de Broadmoor, o jẹ́ ọkan ninú àwọn ibi ìsinmi tí ó dára jùlọ ni Amẹrikà tí ò si dúró dáa ju orí-òkè ti a npẹ̀ ni Rocky lọ (Rocky Mountain) ti gbogbo ènìyàn si dá wọn mọ̀ sí ọ̀sọ́ síse ni àkókò Kérésìmesì. Pasitọ Peteru pè wá lati jẹ̀ ki á mọ̀ pé àwọn yóò wà nibẹ̀ ó si sọ pẹ̀ kí àwa nà wa lati wà pẹ̀lú wọn. A tètè gbá ànfani ore-ọ̀fẹ́ yìí a si lo ọjọ mẹta gbáko pẹ̀lú wọn nibẹ̀.

Ni ìgbà tí a wà pẹ̀lú Pasitọ Peteru, ọ̀rọ̀ lórí iṣẹ́ ìránṣẹ ni a má nsọ́ púpọ̀ jùlọ, niwọn ìgbà ti o wà lọkan mi, ohun na sì ni kókó idí ti a fi rin ìrìn àjò nà. A jọ nsọ̀ ọ̀rọ̀ lórí àwọn èrò wà fún ọdún tuntun ti o mbọ̀ àti jọ pin àwọn èròngbà wa. Ni ìpari, àsikò tó lati tún pínyà, pé ó dàbọ̀, ti ó ma njẹ́ ẹ̀dùn ọkan fún mi nitorí ọ̀rẹ́ àtàtà ni wọn jẹ́ sí wa. Èmi àti Drenda na má nlọ si ọ̀dọ̀ wọn ni New Zealand ni ẹ̀kan lọdún, tàbi ni àrin ọdún mẹjì sí ara wọn, súgbọ́n ninú ọdún yìí iṣẹ́ pọ̀ ni ọwọ́ mi gan ni mi ò si ni lọ́kàn lati lọ.

Àwa ni a ti wá si ile pẹ̀lú ìfojúsọnà nla ninú ọdún titun yìí. Sí ìyànlẹ́nu, síbẹ̀, ni ọjọ kẹsán ninú òsú kinni, ni mo lá àla ti wọn ti sọ fún mi pé Pasítọ Peteru yóò fi ìwe pè mi lati wa wàásù ninú ìjọ rẹ̀ ninú osù kejì ọdún. Mo ránti pé mo nròó pé ki sá bà wáyé bẹ̀. Bí mo ti se wá lo ọjọ mẹ́tà pẹ̀lú rẹ̀ tó, kó ti ẹ da sọ, bẹ́ sì ni osú kejì ni à nwò lọkán yìí. Mo wa sọ́ fún Drenda ohun ti Oluwa sọ fún mi bi mọ tin lọ si ile ìdáná lati se ounjẹ̀ àárọ.

Ni ẹ̀gbẹ́ kan si ilé ìdáná ni mọ gbé ẹ̀rọ́ Kọmpúta mi lé, bẹ́ sì ni mo sì sá bà ma ntàn án silẹ̀. Bí mo ti jókò ti mo nmu kọfí, ni mo ri ti ìfìránṣẹ́ kan wọlé lati ọ̀dọ̀ Pasitọ Peteru. Bí mo ti sí Imeeli ná, o yàmilẹ́nu lati ri pé Pasitọ Peter ni ó npè mi lati wá wàásù ní ibi ìpàdé àpérò ti ètò ìsúnà ọlọ́ dọdún wọn, tí kò si ju ọsẹ̀ mẹta lọ si àkókò na mọ́. Ó yàmilẹ́nu ná, sùgbọ́n nitori àlá ti mo ti lá sáàju kò jẹ́ ki o já mi láyà. Mo tètè lọ wo àwọn ètò ti mo ti kọ sílẹ̀ bóyá yóò se ése fúun mi lati lọ, nitori mo ni ọ̀pọ̀ ibi lati dé ninú osú yìí kan náà ti Pasitọ Peter npè mi lati wá si. New Zealand, Èmi àti Drenda ti setò lati lọ sí Buenos Aries ni Argentina, bi ọjọ́ meló si àkókò na mo ni lati wà ni Auckland. Ọ̀na kan tí ó le mú mi tètè dé si ọ̀hún ni ti mo bá ti kúrò ni ìpàde àpérò ni Buenos Aries, kin si kọjá si Sydney, Australia, kín si wọ ọkọ̀ ofúrúfú ti nlọ sí Auckland. Mi ò ba má mura irú ìrìn -àjò yìí , sùgbọ́n nitorí Oluwa ti ba mi sọ ọ́ tẹ́lẹ̀, mo mọ̀ pé a ni lati lọ.

Ìrìn -àjò lọ si Argentina jẹ́ ìrìn-àjò ajọrìnpọ̀ tí ọkan ninú àwọn oníbárà ile iṣẹ́ ti ilé iṣẹ́ mi nbá sòwòpọ̀ se onigbọ̀wọ́ rẹ̀. ìrìn -àjò ti o dára ni ó sì tún jẹ́ àkòkò nlá lati wà pẹ̀lú àwọn ọ̀rẹ́ mi ti mo má nsábà rí ni ẹ̀kàn ni ọdún. Ni àsikò ti à nsọ yìí ni Argentina nkojú àwọn ìsòro lórí ìsúna orilẹ̀-èdè wọn tí àwọn wàhálà si wáyé ni àwọn ilú nà, sùgbọ́n ju gbogbo rẹ̀ lọ, ìrìn -àjò tí ó ga ni ti ó sì dàbi ẹni pé mi ò tì rin irú rẹ̀ rí ni. Wakàti mẹrìndínlógún ni yóò gbà wá lati dé Sydney ninú ọkọ̀ ofurufú ò jẹ́ ìrìn-àjò ti ó jìnnà ti mó tí rìn rí. Ohun tí o kàn ni lati lọ́ si òkè Ibití Òpó Gúúsù wà, ti mo ti nrò pé ó dára bi mo ti nretí lati ri apá kan ti gbogbo ayé lati inú afẹ́fẹ.

Nigbàtí a wà ninú ọkọ̀ ojú òfúrúfú, bi mo ti nwò lati ojú fèrèsé kò si nkan ti mó rì bikòse yìnyín ati ẹ̀gbọ̀n otútù ti ó nfẹ̀ si mi, nigbànà ni mo ṣẹ̀ṣẹ̀mọ̀ pé mo nrin ìrìn-àjò lorí afẹ́fẹ lọ́ sí Argentina. Ninú ọkọ̀ òfurufú orilẹ́-èdè ti wọn ni ìsòro lórí ètò ìsúná wọn ti wọn nsakitiyan jijàkadi lati fẹṣẹ̀ wọn múlẹ̀. Èrò yí wa sinú ọkàn mi láàrin ìsẹ́jú àyáá pé ti àwọn ilé iṣẹ́ yìí ba ngbà ọ̀nà àlúmọ̀kọ́rọ́yí lati ma tun ọkọ̀ ojú òfurufú wọn se, ti nkan bá wá lọ sẹlẹ́ si nkọ́, kò ni lọ dára tó. sùgbón mo mọ̀ pé àbò mi wà lọ́wọ́ Oluwa, Òun tikararẹ̀ ni o sọ pé kin rin ìrìn àjò yìí.

Bí a tí dé Sydney, ni a ti pe Pasitọ Peteru àti aya rẹ̀ Bev, ohun ìyàlẹ̀nu ni lati gbọ́ pé Pasitọ Peteru wà ni ilé ìwòsàn kàn, pé ó ní àìsàn àrùn ọkàn. Kò sì ni le se ìwàásù kankan ni àkókò ìpàdé àpérò nla ti wọ́n fẹ́ se ni opin

ọ̀sẹ̀ lorí ti ìsúna wọn, ó wá bèrè lọ́wọ́ mi pé mo lé se ìdánilẹ̀kọ́ fún wọn ni gbogbo àkòkò ìpàdé nà, mo wà mọ ìdí ti Oluwa se darí mi sí New Zealand, ínú mi sì dùn bi Ẹ̀mi Mimọ́ ti se tọ ìsísẹ̀ wa. Èyí ni ó mú mi rantí ohun ti ìwe Romu 8:14

**"NITORÍ IYE ÀWỌN TI A SE AMỌ̀NÀ FÚN LÁTI Ọ̀DỌ̀ Ẹ̀MI ỌLỌRUN WÁ ÀWỌN NI ÍSE ỌMỌ ỌLỌRUN."**

**—ROMU 8:14**

"*Nítorí iye àwọn tí a se amọ̀nà fún láti ọ̀dọ̀ Ọlọrun wá, àwọn ní íse ọmọ Ọlọrun"* (Romu 8:14).

Bẹ́ẹ̀ sì ni à nsọ́ nipa agbára lati leè gbọ́ ìtọ́nisọ́nà, èrò àti àgbékalẹ̀ lati ọ̀dọ̀ Ẹ̀mi Mimọ́. Kò tún sí ìtàn kan ninú Bibeli tí ó dára lati sàpèjúwe ẹ̀kọ́ ti ó kàn pé, ni gbigbọ́ ohùn ti Ẹ̀mi Mimọ́ nikan ni ó le fún ọ ni àwọn ìdáhùn ti o nílò, jú ìtàn Daniẹli. Ẹ jẹ́ ki a lọ wo ìtàn nà ninú ìwe Daniẹli 2:1-6.

> *Àti ní ọdún kejì ìjọba rè, Nebukadinéssárì lá àlá: nípa èyí tí ọkàn rẹ̀ kò fi lé lẹ̀ ninu rẹ̀ tí orun fi dá ní ojú rẹ̀. Nígbàna ni ọba paṣẹ pé, kí a pe àwon amòye àti ọlọgbọ́n àti àwọn osó àti àwọn Káldéà wá, láti fi àlá ọba ná hàn fun un. Bẹ̀ẹni wọ́n sì dúró níwájú ọba, ọba sì wí fún wọn pé "mo lá àlá kan, ọkàn mi kò sì lé ilẹ̀ láti mọ àlá nà."*
>
> *Nígbàna ni àwọn Káldéà wí fún ọba ní èdè àwọn ara Sínà pé, "Kí ọba ki ó pẹ́: rọ̀ àlá nà fún àwọn ọmọ-ọ̀dọ̀ rẹ; àwa ó sì fi ìtumọ̀ ná hàn."*
>
> *Ọba dáhùn ó sì wí fún àwọn Káldéà pé, "Ohun na ti kúrò ní orí mí: bí ẹ̀yin kò bá fi àlá nà hàn fún mi àti ìtumọ̀ rẹ̀ pèlú, ao ke yín wẹ́wẹ́, a o sì sọ ilé yín di àatàn. Sùgbọ́n tí ẹ̀yin bá fi àlá nà hàn, àti ìtumọ̀ rẹ̀ pèlú ẹ̀yin ó gba ẹ̀bùn àti ore àti ọlá ní ọwọ́ mi: Nitorína, ẹ fi àlá ná hàn fún mi, ati ìtumò rẹ̀ pẹlú."*
>
> —Danieli 2:1-6

*Àwọn Káldéà sì dáhùn níwájú ọba wọn sì wípé, "Kò sí ẹnìkan ní ayé tí ó le fi ọ̀ràn ọba hàn: Kò sì sí ọba, olúwa tàbí ìjòyè kan tí o bèrè! irú ǹkan bẹ̀ẹ̀ lọ́wọ́ amòye, tàbí ọlogbọ́n tàbí Káldéà kan rí. Ohun ti ó tilẹ̀ sọ̀wọ́n ni ọba bèrè, kò sì sí ẹlòmíràntí ó le fi hàn níwájú ọba bíkòṣe àwọn òrìṣà, ibùgbé ẹnití kì íse nínú eran ara."*

*Nitorí ọ̀ràn yìí ni inú ọba fi bàjẹ, ó si bínú gidigidi, ó sì pàṣẹ pé kí wọn ó pa gbogbo àwọn amòye Bábélì run. Nígbànà ni àṣẹ jáde lọ pe kí wọ̀n kí ó paa àwọn amòye; wọ́n sì ńwá Dáníẹlì pẹ̀lú àwọn egbẹ́ rẹ̀ lati pa wọ́n.*

—Dáníẹlì 2:10:13

*Nígbànà ni Dáníẹlì lọ sí ilé rẹ̀, ó sì fi nkan nà hàn fún Hananiah, Misaeli ati Asariah, àwọn egbẹ rẹ̀ pé, kí wọ́n kí ó bèrè àánú lọ́wọm Ọlọrun, Olúwa ọ̀run, nítorí àṣírí yìí: kí Dáníẹli àti àwọn ẹgbẹ́ rẹ̀. má ba sègbé pẹ̀lú àwọn ọlọ́gbọ́n Bábélì ìyókù, tí o wà ní Bábélì. Nígbànà ni a fi àṣírí nà hàn fún Dáníelì nínú ìran ní òru, Dáníẹlì si fi ìbùkún fún Ọlọrun Olúwa ọ̀run. Dáníẹli dáhùn o sì wípe, "Olùbùkún ni orúkọ Ọlọrun títí lai: nítorí tìrẹ ni ọgbọ́n àti agbára. O sì ńyí ìgbà àti àkókò padà: ó ńmú ọba kúrò, o sì ńgbé ọba lékè; o sì ń fi ọgbọ́n fún àwọn ọlọgbọ́n; àti ìmọ̀ fún áwọn tí o mọ̀ ọ́n ye,* ***<u>O fi ohun ìjìnlẹ̀ ati àṣírí hàn; o mọ ohun tí ó wà ní òkùnkùn, lọ́dọ̀ rẹ̀ ni ìmọ́lẹ̀ sì wà."</u>***

—Dáníẹlì 2:17-22

Daniẹli wà ninú ipo ìye àti ikú, ni ibi tí o léwu. Sùgbọ́n ó jẹ́ kọ́kọ́rọ́ si ìgbéga ti o kàn. Ọlọrun lòó lati gbe si ibi gíga, ki ise fún ìsubú rẹ̀. Daniẹli le seé nipa ìrànlọ́wọ́ ti ìmọ̀ àsírí Ẹ̀mi Mimọ́, lati le túmọ̀ àlá ọba Nebukadnessarì. Ọba sì ngbọ̀n, ó sì dojú bolẹ̀ bi a ti se rìí ninú ẹṣẹ̀ ti o tèlé.

*Nígbànà ni Nabukadnéssárì, wólẹ̀ ó sì dojú rẹ̀ bolẹ̀, ó sì fi orí balẹ̀ fún Dáníẹlì, ó si pàṣẹ pé kí wọn kí ó se ẹbọ-ọrẹ olóorùn*

*dídùn fún un. Ọba dá Dáníẹlì lóhùn pé; lóòtọ́ nipé Ọlọrun yín ni Ọlọrun àwọn ọlọrun àti Olúwa àwon ọba, àti olùfihàn gbogbo àṣírí, nítorí ti ìwọ le fi àṣírí yìí hàn."*

***<u>Nígbàna ni ọba sọ Dáníẹlì di ẹni-ńlá, ó sì fún ni ẹ̀bùn ńlá púpọ̀, ó sì fii jẹ olórí gbogbo ìgbèríko Bábélì àti olórí onítọjú gbogbo àwọn ọlọgbọn Bábélì.</u>*** *Dáníẹli sì bèrè lọ́wọ́ ọba ó sì fi Sádrákì. Mésákì ati Àbẹ́dnégò jẹ olórí ọ̀ràn ìgbèríko Bábélì: ṣùgbọ́n Dáníẹlì jóóko ní ẹnu-ọ̀nà àfin ọba."*

—Dáníẹlì 2:46-49

Kín wá ni èsì àbájáde tí Daniẹli ti o gbọ́ ohùn Ọlọrun? ìgbéga àti ọrọ̀!

Atún le rí irú ìtàn yìí kannà ninú Bibeli, ìtan Josẹfu. Ti óun nà ni ìdojúkọ bákanna, Wọ́n fún Josefù ni ayè lati túmọ àlá Fárao. Bi o ti lẹ́ túmọ̀ àlá na àti sètò ìsàkóso lati gba ilẹ̀ Ejibiti lọ̀wọ́ ogun ìyàn ti o mbọ̀ èyíti àlá Farao fihàn wọn, a o rí àwọn ìdáhùn Farao ninú ìwe Gẹnẹsisi 41:39-40.

*Fárao sì wí fún Jósẹ́fù pé, "Níwọ̀nbí Ọlọrun ti fi gbogbo ńkan yìí hàn ọ́, kò sí ẹnití ó se amòye àti ọlọgbọ́n bí ìwọ, ìwọ ni yóò se olórí ilé mi, gẹ́gẹ́ bí ọ̀rọ̀ rẹ ni ao sì ma se àkóso àwọn ènìyàn mi; ìtẹ́ ni èmí o fi tóbi jù ọ́ lọ."*

—Genesisi 41:39-40

Ninú àwọn ìtàn wọ́nyìí, ipò àinirèti jẹ̀ ìdànwò ni ìbẹ̀rẹ̀, sùgbọ́n ìgbéga àti ọrọ̀ ni èsì àbájade rẹ̀. Ninú ayé wọn le san owọ́ tó niyé lórí fún ẹni ti ó bá wọn yanjú àwọn ìsòro nla. Sùgbọ́n Ẹ̀mi Mimọ́ inú rẹ fẹ́ràn lati máa gbé ọ sí ibi ti ó yẹ láàrin àwọn wàhálà nlá. Mase bẹ̀rù nigbati ó ba nsẹlẹ̀, bikòse kí o bẹ̀rẹ̀ si ni yin Oluwa, ti yóò ràn ọ́ lọ́wọ́ bí o ti se ran Daniẹli àti Josefú lọ́wọ́! Mo má nfí ìgbàgbogbo sọ wipé ti Ọlọrun ni Ògo, ó sì ma nsán fún mi padà! Mo ni ìfẹ́ si ohun ti Daniẹli sọ nipa Oluwa '***<u>O fi ohun ìjìnlẹ̀ ati àsírí hàn; o mọ ohun tí ó wà ní òkùnkùn, lódọ̀ rẹ̀ ni ìmọ́lẹ̀ sì wà."</u>*** Daniẹli sọ pé ìmọ́lẹ̀ na ngbé pẹ̀lú mi. Tí ó túmọ̀ si pé, bi kí ènìyàn máa rìn jade kúrò ninú òkùnkùn, lẹ́yìn tí o tan iná, óò lé ríran rí

ibití o bá nlọ̀! Ìmọlẹ̀ ti borí òkùnkùn wà si mọ ibití ó yẹ kí o rìn. Paulu na sọ̀ ọ̀rọ̀ yìí ninú ẹṣẹ náà pé Ọlọrun ti sọ̀rọ̀ àti gbà wá ni àsikò wàhála.

*"Ẹ̀yin mọ̀ pé nígbàtí ẹ̀yin jẹ́ kèfèrí, a fà yín lọ sọ́dọ̀ àwọn* ***odi*** *òrìsà, lọ́nàkọnà tí a fà yín"* (1 Korinti 12:2).

Paulu nsọ nibiyìí pé òrìsà kì I sọ̀rọ̀, sùgbọ́n Ọlọrun à ma sọ̀rọ̀!

Nibayìí, ó le má yà ọ́ lẹ́nu pé kilódé ti mo fi pe àkòrí orí yìí ní "Ibi ìgbéga tí ó le koko" Nitorí ibi ayè ti o le ni Ẹ̀mi Mimọ́ inú rẹ ti gbé ni ìdáhùn. Ibiti ó le nà ni ó ti le ni ànfàni lati mú ọ̀nà àbáyọ wá. Ibití ó le ni ibi àsepé fún ìpele ìgbéga rẹ tó kàn! Ó se ni láanu, ọ̀pọ̀ àwọn onigbàgbọ́ ni wọn má yọ ara wọn kurò ni ibiti o le. Kódà, ọ̀pọ̀lọpọ̀ ni o máa nrò wipẹ̀ ti àwọn bá ti bá ara wọn ni ibití ó le,wọn ti ṣẹ Ọlọrun ni.

Mo ránti ìgbà ti a ṣẹ̀ṣẹ̀ bẹ̀rẹ̀ si ni se èto lórí Tẹlifisọnu, ti owó wá nlọ bí i ẹgbẹ̀rún mẹ́sàán pọ́ùn ni osù kan. Ọ̀rẹ́, mo lérò pé owó yìí ti pọ̀ jù ni osù kọ́kan, nigbàti ó yá ó gbéra lọ sí ẹgbàáwá pọ́ùn ni osù kan, àti nigbà tí ó si yá o gbéra lọ sí ọ̀kẹ́meji abọ́ pọ́ùn ni osù. Ni ọjọ́kan gbogbo wà ni ibití a ti ngbàdúrà ni Amy, ọmọ mi obinrin, ba bẹ̀rẹ̀ si ni sọ̀rọ̀ nipasẹ̀ ẹ̀bùn àsọtẹ́lẹ̀.

"Ìkórè nà ti tóbi jù fún ọ, mo sì n mú ọ fẹ̀ si. Nipaṣẹ̀ Ẹ̀mi mi nikan ni o ti se le ní òye ohun tí ó fẹ́ sẹlẹ̀! Ó yá jáde wa jẹ́ kí ndarí rẹ si ibi awọn ohun tó le kọjá òye rẹ, àwọn kò sé ése?"

Kín to sọ̀ ìtàn, ti o dá le àwọn ohun ti o ti mọ̀ fún ọ̀ bayìí, se o le sọ fún mi bí a ti se le túmọ́ nkan yìí? ÌGBÉGA! Mo fẹ̀ bi o ti sọ fún mi pé kín yàn ohun ti mo fẹ́. Ó nbèrè lọ̀wọ̀ mi bóyá mo nifẹ́sí pé ki o mú mi rin ọ̀nà to jìn pẹ̀lú Rẹ̀. Ó fẹ́ mọ̀ boyá má sọ pé rárá, Kò bá lọ si ọ̀dọ̀ ẹlomiràn, Ó dá mi lójú bẹ́. Sugbọ́n má kúkú gbà ìgbéga nà fún ara mi, ti o bá se ìwọ nà nkọ́?

Ó dáa, mo sọ́ pé" Bẹ́ẹ̀ni Oluwa, ó mọ̀ pé máse é" Lẹ́yìn ọ̀sẹ̀ bi melo sí ìgbànà, àwọn ilé iṣẹ́ Daystar gbé iṣẹ́ fún wà ti a o má se ni ojojúmọ́, kí ó sì tó di ìgbànà ọ̀sẹ̀ọ̀sẹ̀ ni a gun orí afẹ́fẹ́. Ti a bá ti gbà iṣẹ́ yìí, ti a si gbe lọ si orí Tẹlfisọnu à jẹ́ wipẹ̀ owó tí a ó ma san ni osù yóò jẹ̀ ẹgbàáwá pọ́ùn. Nitori idi èyí ti nse ọ̀rọ̀ àsọtẹ́lẹ̀ àti ìmísí ti Ẹ̀mi Mimọ́ ti ó wà ninú mi, mo sọ́ pé bẹ́ẹ̀ni. Gbobo àwọn ènìyàn sọ fún mi pé fún bi osù diẹ, o le ma rẹ̀yín lorí afẹ́fẹ́ nitorí owó rẹ̀ ni sisan tító àwọn èníyàn yóò fi mọ ètò nà lorí afẹ́fẹ́. Nkan gàn ti o sẹlẹ̀ si wa nìyìí, boya ó tún le diẹ̀ ju ohun ti a lerò lọ.

Ni àrin osù maarún, owó ti lọ si ẹ̀dẹ́gbẹ̀ta ẹgbẹ̀run pọ́ún ti a o san ni orí iṣẹ́ Tẹlifisọun . Kóda aláṣẹ ile iṣẹ́ na ti kòwe ranṣẹ́ si wà nitori ti a kó tètè ma sàn owo wa.

Mo wa bẹ̀rẹ̀ sí ní jìjàkadì pẹ̀lú Ọlọrun nipá rẹ̀, pé orukọ ti a tún npe ètò yìí nà ni *Yanjú ọ̀rọ̀ owó!* Ìrẹ̀wẹ̀sì ti fẹ̀ maà mú mo ti sọ fún Drenda pé ó se ése kí npa ìsẹ́ ti orí Tẹlifisọ́un tì. Ìdahùn rẹ̀ náà ni pé " kín ni Ọlọrun sọ́ ?. Ó ni óun o san owó rẹ̀, àbí?. Fún bi ọjọ́ melo kan ti mo bá ti sọ̀rọ̀ nipa rẹ̀ oun ti o nsọ na nìyìí. Ó dáa, a gbadúrà, lóòtọ́ mi ò gbọ́ ohun kankan nipa rẹ̀ ni àsikò nà, sugbọ́n mo ni ìmọ̀ àlááfià ti Ọlọrun. Ninú ọ̀sẹ̀ nà, mo lá àla nibití mo ti rí ọ̀pọ̀ sọwédowó ti wọn tò lera wọn. Nkan ti o wá sàjẹ̀jì si mi nipa àla yí ni wipé ki íse pé mo rí sọ̀wédowó yìí nikan, mo ri iye owó ti wọn kọ síi àti ẹni tí o kọ wọ́n. Nigbàti mo tají, mo mọ̀ pé wọn ti san owó ti a fẹ́ san ni ile iṣẹ́ Tẹlifisọ̀un, ọkan mi sì balẹ̀. Ó dáa, ni opin ọ̀sẹ̀ nà mo le sọ pé,ẹ̀dẹ́gbẹ̀ta ẹgbẹ̀rún wọlé wá bi a ti se fihàn mi lojú àla mi. iye ti mo rí pé wọn kọ àti ẹniti ó kọ ọ́ gbogbo rẹ̀ ni ó wà nibẹ̀.

Awọn ibiti ó bá le ki íse ibití kò dára; Ibi àyè ìgbéga ni, ọ̀rẹ́ mi. Awọn èniyàn má nsọ wipé àwọn ma nbẹ̀rù lati wà ni ibi tí o ba le, torí ki àwọn má ba se àsìse. Sùgbọ́n Ẹ̀mi Mimọ́ le kì ọ́ nilọ̀ kí o má ba se àsìse púpọ̀ ti o ba ntẹ́tí sílẹ̀ sí i.

Mo rànti, nigbàti mo ni ile iṣẹ́ a yánilowó/ àti fi nkan dógò ni bi ọdun diẹ sẹ̀yín ti onibarà kan fẹ́ lati ya ninú ohun ti o ní ninú ile rẹ̀ fi dókòwò ni ile iṣẹ́ kan ti mi o fi taratara gba ti ẹ. Mo ranti bi mo tin gun ori pẹ̀tẹ̀si ile nà nlọ, ọkan lara àwọn àsojú mi ba mi sọ̀rọ̀ nipa rẹ̀, Lojiji, ni mọ mọ̀ pé Ẹ̀mi Mimọ́ nsọ ohun ti màá se fún mi nipa ọ̀ràn nà. Mo wa sọ́ fún àsojú nà pé, "o le se iṣẹ́ nà, sugbọ́n ri dajú pé oníbára nà fọwọ́siwe ti àkọ́silẹ̀ rẹ̀, yóò jẹ̀ ara ti ẹ̀yáwò ti o fẹ̀, ti o si kọ́ sibẹ̀ pé ile iṣẹ́ wa kò ni nkan se pẹ̀lú ilé iṣẹ́ ti ó tí fẹ́ se idókówò súgbọ́n àwa kan f ún un ni ẹ̀yáwó ti o bèrè fún ni"A tún kọ ọ́ silẹ̀ pé a kò ni ọwọ́ ninú ìdókòwò ti ó fẹ́ lati se tabi pé bóyá a fọwọ́ si pé ki o se ìdókòwò pẹ̀lú ilé ìsẹ́ nà. Lẹ̀yìn bí osù mẹfà gbogbo rẹ̀ fọ́júpọ̀. Ile iṣẹ́ nà pàdánu gbogbo owó àwọn onibarà wọn. Wọ́n sì gbé ilé iṣẹ́ ìdokowò na lọ si ilé ẹjọ́ ati ilé iṣẹ́ tèmi nà pẹ̀lú. Sibẹ̀síbẹ̀, nigbati àwọn

**O LE GBẸ́KẸ̀LÉ Ẹ̀MI MIMỌ́ LATI RÀN Ọ́ LỌ́WỌ́ ÀTI DARÍ RẸ NÍNÚ GBOGBO ONIRÚRÚ ÀWỌN IPÒKÍPÒ.**

aláṣẹ rí lẹ́tà ti mo ní kí onibarà mi fọwọ́sí, ni ilé ẹjọ́ ni ki a má lọ.

Ẹ̀mi Mimọ́ ni ó dami dúrò ni ipa ọ̀nà mi si àtẹ̀gùn tí mo sì ti sọ fún asojú mi lati fi lẹtà nà sí àyé àwọn ti a ti setán pẹ̀lú wọn. O le gbẹ́kẹ̀lé Ẹ̀mi Mimọ́ lati ràn ọ́ lọ́wọ́ lati le dari rẹ ninú gbogbo onírúrú awọn ipokípo. Gẹ́gẹ́ bi Jesu ti sọ, “Máse bẹ̀rù.”

Mo ti sọ ìtàn yìí ninú ọ̀kan àwọn ìwe tókù, sùgbọ́n ó tún jẹ yọ ninú ìjíròrò wa yìí. Ni ọjọ́ kan èmi àti ẹbí mi lọ fún ìsinmi opin ọ̀sẹ̀ ọlọjọ́ mẹta. Gbogbo wa ti wà ninú ọkọ́-ẹrù, bí mo ti fẹ́ sáná si ọkọ̀, lojiji, ni Ẹ̀mi Mimọ́ sọ fún mi lati gbe ọkọ̀ ayọkẹ́lẹ́ mi. Mo ni ọkọ̀ ayọ́kẹ́lẹ́ wa kàn ni òpópóọ̀nà lẹ́gbẹ ọkọ̀ -ẹrù nà. Ẹ̀mi Mimọ́ ni kin gbé ọkọ̀ na lọ si orí pápá. O jẹ́ ajèjì simi. Mo ròó pé, “kilódé tí Ẹ̀mi Mimọ́ fi sọ́ fún mi lati gbé ọkọ̀ na kurò nibẹ̀ kin si gbé sọ́rí pápá? Kò yé mi. Sugbọ́n mo mọ̀ pé onidí. Mo wá sọ fún Drenda ohun ti mo gbọ́ mo si sọ̀kalẹ̀ lati lọ gbé ọkọ̀ na kurò nibiti ó wà si ibiti Ẹ̀mi Ọlọrun sọ pé kin gbé sí. Mi ò ti ronú lorí rẹ̀ tití di ìgbà ti a padà de ilé ni àsálẹ́ ọjọ́ ìsinmi. Ni mo ri pé igi nla kan ti wó sí ọ̀gangan ibiti a gbé ọkọ̀ mi nà sí. Kò si sí ohun tí ó kan ọkọ̀ nà nibiti Ẹ̀mi Mimọ́ ni kí a pàda gbe si. Tí ó ba jẹ́ pé a kò gbé kùrò ni ibití ó wà tẹ́lẹ̀ ni kò ba bajẹ́ pátá ni.

Èmi àtí Drenda, dájúdájú, wa di ọmọ ti wọn ngbé àwòran wa kiri lori ohun ti kò yẹ kí a fi owó se. Ohun gbogbo ti a si nilò ni ki a mọ́ nipa àwọn àsirí ìlànà àti àwọn ọgbọ́n ìjìnlẹ̀ lati lé gà ju gbogbo àyídáyidà lọ. Nibáyìí, mo ti layọ̀ pẹ̀lú ètò wa lorí Tẹlifisọ̀nu, ti gbogbo ènìyàn nwò káàkiri ayé ti a npe ni *Yanjú ọ̀rọ̀ owó*!

Ọ̀rẹ́ mi, ibiti kádàrá rẹ wà lonìí nìyíì.

*“Tí a sọ di alágbára ninú àìlera, tí wọn di akọní ní ìjà, wọ́n lé ogun àwọn àjèjì sá’* (Hébérù 11:34b)

Ibiti ó dabi pé ó le àti bí i pé kòséese, kò lé wọn si séese ti o ba ti mọ ìdáhùn wọn!

ORÍ KẸSÁN AN

# OHÙN KẸ́LẸ́, KÉKERÉ NÁÀ

Nigbati mo bẹ̀rẹ̀ ìdanilẹ́kọ́ lórí ohùn ti Ẹ̀mi Mimọ́, ọ̀pọ̀lọpọ̀ àwọn ènìyàn ni wọn sọ fún mi pé àwọn kò gbọ́ ohùn Ọlọrun ri. Sùgbọ́n mo má nfi ìgbà gbogbo sọ fún wọn pé "Bẹ́ẹ̀ni, o ti gbọ́ọ!" Tí ó ba jẹ́ pé ìwọ nà pẹ̀lú àwọn ti wọ́n ni àwọn kò ti gbọ́ ohùn Ọlọrun rí, jọ̀wọ́ sí Bibeli rẹ si Àwọn Ọba kinni 19:11-12.

> *Olúwa sì wípé, jáde lọ, kí o sì dúró lóri òkè níwájú Olúwa, sì kíyèsii, Olúwa kọ́ja.*
>
> *Ìjì ńlá àti líle sì fa àwọn òkè ńlá ya, ó sì fọ́ àwọn àpáta tútú níwájú Olúwa; sùgbọ́n Olúwa kò sí nínú ìjì na àti lẹ́hìn ìjì na, ìṣẹ̀lẹ̀ sùgbọ́n Olúwa kò sí nínú ìṣẹ̀lẹ̀ na. Àti lẹ́hìn ìṣẹ̀lẹ̀ na iná; sùgbọ́n Olúwa kò sí nínú iná nà, àti lẹ́hìn ina, ohùn kẹ́lẹ́ kékeré.*
>
> —Awon Oba ikinni 19:11-12

.

Biótílẹ̀jẹ́pé, mo ti gbọ́ ohùn Ẹ̀mi Mimọ́ ni onirúrú ọ̀nà; ohún ti Ẹ̀mi Mimọ́ ni ohùn kẹ́lẹ́. Ó jẹ́ ohùn kekeré, ohùn kẹ́lẹ́. Bi mo ti sọ́ sáájú ninú ìwe mi kan, ohùn Ọlọrun má dún bi èrò ti gbọ̀n pẹ̀lú orísí ìtanijí. Gẹ́gẹ́ bi o ti se le dá ohùn ọmọ rẹ mọ̀ láàrin ọ̀pọ̀ àwọn èrò, o le bẹ̀rẹ̀ si ni mọ Ẹ̀mi Mimọ́ nà dáadáa ati lati dá ohùn rẹ̀ mọ̀ nigbàti ó bá sọ̀rọ̀ bàkanna. Sugbọ́n ninú ìpín yìí, mo fẹ́ ba ọ sọ̀rọ̀ nipa ohùn Ọlọrun tí kò sí ẹnikan ti o nrónú nipa rẹ̀, sugbọ́n ti gbogbo yín si ti gbọ́.

Nigbàti mo wà ni ile ìwe gíga ti Oral Roberts unifasiti, mo lo fún ọpọ̀ àwọn ẹ̀kọ́ ninú Bibeli pàápa ninú Májẹ̀mú Laílaí. Ọ̀pọ̀lọpọ̀ awọn àlàye ni

ó wà ti mi o ti kọ́ nipa rẹ̀ tẹ́lẹ̀. lóótọ́; mi ò ti kọ nipa rẹ̀ tẹ́lẹ̀, Pẹ̀lú bi mi o ti se kàwé parí ni girama, nise ni mò ngbìyànju lati lé dí àwọn àlàfo nà; pàápá jùlọ́ ni ọ̀sẹ̀ ti mo ti setán tí mò npaí tàn lọ. Ninú kílási ti mò nsọ yìí mo ní lati kọ àkòrí kan lorí Májẹ̀mú Laílaí, èyí ti mi ò si le rantí ni àsikò nà. Ìwe kíkọ máa ndẹ́rùbàmi. Nigbàti mo ṣẹ́sẹ̀ dé kọ́lẹ́ji, ni ọdún nà, mo ni lati kọ ìwe mi àkọ̀kọ́, nigbati mo gba ìwe nà padà, ọ̀pọ̀lọpọ̀ ni o wa nibẹ̀ ti wọn si fi yínki pupa kọ gbogbo ojú ìwe nà pe" bẹ́ẹ̀ni ó lọ si ile ìwe girama bayìí?. ni wọn kọ sábẹ́ ìwe nà, mi o gbédè Gẹ̀ẹ́sì bẹ́ni ti mo ba sì nsọ èdè gẹ́ẹ̀sì yìí o burú jaì ti ó si ma nya àwọn olukọ́ mi nà lẹnu pé bawo ni mo se de ORU. mo ni lati wa ẹniti yòó ran mi lọ́wọ́ ninú èdè Gẹ̀ẹ́si ni ọdún àkọ́kọ́ mi ni ilé ẹ̀kọ́ na.

Bayìí, pẹ̀lú gbogbo àkitiyan lorí ọ̀sẹ̀ ti o gbẹ̀yìn yìí, ìwe mi ti tún wa nilẹ̀ ti ó tí yẹ kin kọ. ẹ̀rù ìsẹ́ àkànse na n bà mi. Mo ni lati joko kin kọ́ ìwe nà, sùgbọ́n kò si ẹniti ó kọ́ mi bi a tisé nkọ̀we; torí ìdi èyí mà kàn wa ibikan lati lọ da àwọn ọ̀rọ̀ kan kọ ti ma si se àwọn àtúnse ránpẹ́ ki ẹnikẹ́ni ma bá mọ̀ pe mo lọ dàákọ ninú àwọn ìwe miràn. Ọkàn mi mọ́ nitorí èmi kò ri bi nkan ti kò dára, mo tún ma sàtúnkọ àwọn nkan ti mo bá ti kà si bi o ti se yé mi. sùgbọ́n òtítọ́ ni pé èmi kò mo ìwe kọ́. Kóda, kò si àyè fún mi tó ni àsikò yìí.

Ọ̀rẹ́ mi kan wa ti a jọ́ ni iṣẹ́ ni àsikò kan nà ti èmi ti lerò pé àsikò ti yóò se tirẹ̀ yàtọ̀ ni ọjọ na. Gbogbo àwa ti a wà ninú kilásì ni a o jọ kọ ìwé lorí àkòrí kannà, mo wa bi ọ̀rẹ́ mi pé boya ó le jẹ́ kin wòó bi o ti se ètò àgbékalẹ̀ ìwe tirẹ̀. Bayìí, fún àwọn ìdi kan, niketé ti mo ri àwọn nkan ti ó kọ, ni mo ti mọ̀ pé èmi o le kọ ìwe to dára bi o ti se kọ tirẹ̀, mo pinnú lati dàákọ. mo mọ̀ pé ó le pa ọ láyà. Ránti pe ọmọ si ni mo jẹ́ ninú Kristianiti ni akòkò nà. Ódá, kì íse gbogbo ìwé rẹ̀ ni mo dàkọ, sùgbọ́n o tó ìdaji ti mo dàakọ sinú ìwe tèmi loju ẹsẹ̀. Ni opin ọ̀sẹ̀ yìí, Mo sọ́ ìwé nà dì ọjọgbọ́n, ara tùmi pé ìwé kíkọ ti parí. Sùgbọ́n nkankan sẹlẹ̀ ti o kọ mi ní ẹ̀kọ́ ti o se iyebíye ni gbigbọ ohùn Ọlọrun.

Bi mo ti bọ́ sorí ìbùsùn mi ni alẹ́ ọjọ́ nà, mi ò rí orun sùn. Ẹ̀rí ọkàn mi npaíwo sokè mi o si rí orun sùn. Mo wa ri pé ohun ti mo se kò dára, mo ti jalè mo si ti parọ́. Bakannà, mi o bọ̀wọ̀ fún ọ̀rẹ́ mi nà mo si tún ti tàbùkù rẹ̀. Inú mi bajẹ́ gàn! Ni déédé agogo mẹta órú ni afẹ̀júmọ́, mo gba yàrá ọ̀rẹ́ mi lọ, mo si lọ jíi lójú orun, mo sọ ohun ti mo se fún un, mo si bẹ̀ẹ́. Ó

wá wò mi bi orun ti se wà lojú rẹ̀ nà, ó ni " Padà lọ sùn Gary." Ó si padà sórí ibùsùn rẹ ó sùn lọ.

Ni ọjọ́ keji mo lọ bá ọ̀jọ̀gbọ́n tin se olukọ mi mo si sọ ohun gbogbo ti mo se fún un. Lóòtọ́, ó yẹ ki o fún mi ni F ninú àwọn iṣẹ́ nà,sùgbọ́n ó kàn rẹrìn músẹ́ ó ní mo mọ rírì pé ó wá bámi. Ó wá sọ pé nitorí pé mo wá báa, óun yóò si tun fún mi ni B ninú iṣẹ́ ti mo se fún ọdún nà. Ọkan mi wá balẹ̀, ara mi tun yá síi, mo ríi pé ohùn ìdálẹ́bi dákẹ́jẹ́, mo ni ominira mo si ri àlááfià.

Jẹ́ ki nbi ọ lérè ìbérè kan, "kilódé ti ọ̀rẹ́ mi fi padà si orí ibùsùn ti o si sùn lọ nigbàti mo wa ni inú irú ìrora ọkan bẹ́ẹ̀? Kílóde ti òun nà kò se wà ni irú ipò bẹ́ẹ̀ bakannà? Kílódé ti mi o fi le sùn, kíló sì dé ti inú mi se bàjẹ́. Ohùn kan nbami sọ̀rọ̀ ni gbogbo igbà ti mo ba gbiyànjú lati lọ sùn. O ndamilẹ́bi, ẹ̀rí ọkàn mi ni! Ìtumọ̀ ẹ̀rí-ọkàn ni; ìmọ̀inú ti mi mọ ohun ti o tọ́ àti ohun tí kò tọ́ (àsise). Ohun tí ọ̀rọ̀ na túmọ̀ sí gan ni "latí mọ̀ pẹ̀lú" tàbi "lati ni ìmọ̀ ti."

Bi fitílà, ti ìmọlẹ̀ rẹ̀ mọ́lẹ̀ lati fi okùnkùn hàn. Ó ma pa àkọsílẹ̀ èro ọkan gbogbo mọ ni pípé àti ohun gbogbo ti ó ti se. Bi ẹlẹ́rí ninú gbọ́ngàn ìdájọ, ó ma jẹrí si àwọn ohun ìkọ̀kọ̀ gbogbo. Ó ma nsọ̀rọ̀ àti rán ọ létí lati se ohun ti o tọ́ àti yàgò fún àsise/ohun ti kò tọ́. Ẹ̀rí-ọkàn ni ohùn inú ti Ọlọrun ninú ẹnikọkan. Ẹ̀rí-ọkàn máa npé ọkùnrin tàbí obinrin lati ma sirò ìse wọn. Ẹ̀rí-ọkàn má npe ẹnikọkan lẹ́jọ́ bi ìgbà ti ó wà ni gbọ́ngàn ìdájọ lati sírò ohun ti ó ti se niwajú Ọlọrun. Bi wọn ti má npé ẹlẹ́rí siwáju lati wa fi ẹrí rẹ̀ hàn, bẹ́ẹ̀ ni ẹ̀rí-ọkàn wa yóò ti máa sọ̀rọ̀ ni torí wa lati (gbèjà) tàbi dá wa lẹ́bi (fẹ̀sùn kan) wá.

Ìwadi kan ti àwọn Medical Xpress jẹ́risí ni pé:

"Àwọn àlàyé tí ó ti nmúlẹ̀ nipa ìdàgbàsokè ẹ̀dá ènìyàn ni pé, èniìyàn bẹ̀rẹ̀ ìgbé ayé rẹ̀ ni ipò aini ìwà/ẹ̀kọ́, sùgbọ́n pẹ̀lú ìwádi ti ode ìsínyìí ti o ti tako ara wọn. Àwọn oluwádi ti ri pé àwọn ọmọ ọwọ́ bi ọmọ osù mẹfa ti ni ẹkọ́ ti ìdájọ, wọn si lerò wipé a ti lé bi wa pẹ̀lú kóòdù ìwa líle ti a ti firànṣẹ́ sinú ọ̀pọ̀lọ wà"[3]

*Àti nipa èyí ni àwa ó mọ̀ pé àwa jẹ́ ti òtítọ́ àti pé àwa o sì dá ara wa lójú níwájú rẹ̀. Nínú ohunkóhun tí ọkàn wa bá ńdá wa lẹ́bi, nítorímpé Ọlọ́run tóbi ju ọkàn wa lọ, ó sì mọ ohun gbogbo.*

**ẸRÍ- ỌKÀN JẸ́ OHÙN ỌLỌRUN NINÚ GBOGBO ỌKÙNRIN ÀTI OBINRIN, OHUN ÌSÀMÌSÍ TI ẸLẸ́DÁ ÀTI ÀWỌN OHUN TÓ BÈRÈ LATI LE. GBÉ IRÚ AYÉ TÍ Ó DÁ WA FÚN LÀTI GBÉ.**

*Olùfẹ́, bí ọkàn wa kò bá dá wa lẹ́bi, ǹjẹ́ àwa ní ìgboyà níwájú Ọlọrun"*

—1 Johannu 3:19-22

Ẹ̀rí-ọkàn jẹ́ ohùn Ọlọrun ninú gbogbo ọkùnrin àti obìnrin.ohun ìsàmìsí ti ẹlẹ́dá àti àwọn ohun tó bèrè lati le gbé ìrú ayé ti o dá wa fún lati gbé. Kò si ẹnikan ti ó le bọ́ lọ́wọ́ ẹ̀rí-ọkàn rẹ̀. O máa nyàmilẹnú pé ẹni tí ó lọ pàyàn tabi ja banki kan lólè tí o si rò pé o ti parí síbẹ̀, wọn o kàn yí padà lojiji. Sùgbọ́n nisisiyí mo ti mọ̀ pé kò si ìdánilágara kan ti ó to ẹ̀rí-ọkàn tí ó má ndá èniyàn lẹ́bi ẹ̀ṣẹ̀! Paulu sọ ninú ìwe Kọrinti kinni ori èkínní ẹṣẹ̀ kejìlá ti ẹ̀rí-ọkàn njẹ́rísí, ó sọ pé.

*"Nitorí èyi ni ìsogo wa, ẹ̀ri-ọkàn wa, pé ni ìwà-mímọ́ ati òdodo Ọlọrun kid íse nípa ọgbọ́n ara bíkòse nípa ore-ọ̀fẹ́ Ọlọrun, ni àwa nhùwà ni ayé, ati si yìn nị̀ ọ̀pọ̀lọ́pọ̀"*

—2 Korinti 1:12

Óle sọ́ wipé, àṣẹ wo ni ẹ̀rí-ọkàn nlo lati fi sọ̀rọ̀? Kilòdé ti ẹ̀rí o fí dúrò sokè ninú gbọ̀ngàn ìdajọ t'ẹ̀mi ? Nitorí ohùn Ọlọrun ni. Paulu, tún sọ̀ ninú ìwe Romu 2:14-15, ó sọ fún wa pé ẹ̀rì-ọkàn máa nba wa sọ̀rọ̀.

*Nítorí, nígbàtí àwọn kèfèrí, tí kò ní òfin bá se ohun tí ó wà nínú òfin nípa ẹ̀dá, àwọn wọ̀nyìí tí kò ní òfin, jẹ́ òfin fún ara wọn. Àwọn enití o fi hàn pé, a kọ̀wé ìse òfin sí wọn ní ọkàn, tí ọkàn wọn sì jẹ́ wọ́n lẹri, ti ìrò wọ́n láàrin ara wọn sì ńfi wọ́n sùn, tàbí ti o ńgbè wọ́n"*

—Romu 2:14-15

Gbogbo ènìyàn ni o ni ẹ̀rí-ọkàn. O le saìgbà. O le mọ́ àwọn ènìyàn ti o dà bi ẹni pé wọn o lẹrí ọkàn. Sùgbọ́n mo fi dá ọ lojú pé wọn ti bẹ̀rẹ̀ ni. Ti ẹnikan bá nsàtakò ohùn ẹ̀rí-ọkàn wọn ohùn nà yóò ma sálọ diẹ diẹ.

*"Nípa àgàbàgebè àwọn tí ńsèkèe, àwọn tí ọkàn àwọn tìkarawọn dàbí èyítí a fi irin gbígbóná jó"* (1Tìmótíù 4:2)

Paulu nsọ nibíyìí péàwọn ènìyàn wọ̀nyìí ti sun ẹ̀rí-ọkàn wọn, tàbi pé wọn ti sọ ara wọn dí kò ni ìmọ̀ara fún ẹ̀rí ọkàn wọn tàbi gbọ́ ohùn ẹ̀rí-ọkàn wọn nitorí tí wọn ti se ọkàn wọn le. Ronú nipa àwọ̀ ara rẹ, ti o ba ti sún, ti ó túmọ̀ si pé o ti finá jóo, yó ti kú, àyàfi ti òmiràn bá tún sọ jáde, ti èyítí o ti kú nà bá gbẹ dànù ni o tó le ni ìmọ̀lára. Bákanna ni ẹ̀rí-ọkàn wa. Ẹ̀ri-ọkàn kò le mú ọ lati se ohun kóhun—ó má nsọ̀rọ̀. O le ma kọbi ara si tàbi ki o tánù. Sùgbọ́n Paulu tí se ìkìlọ̀ pé ti o bá saìgbà ẹ̀rì -ọkàn rẹ̀ gbọ́, ó le fa wahalà nla bá ọ; tàbi bi Paulu ti se sọ pé o le rí ọkọ̀ ayé rẹ.

> *Àsẹ yìí ni mo pa fún ọ, Tímótìù ọmọ mi, gẹ́gẹ́ bí ìsọtẹ́lẹ̀ wọnnì tí o ti saájú lórim rẹ, pé nípa wọn kí ìwọ kí ó le má ja ogún rere: Máa ní ìgbàgbọ́ àti ẹ̀rim-ọkàn rere; ẹ̀yítí àwọn ẹlòmíràn tanù kúrò lọ́dọ̀ wọn tí wọ́n* ***sì ri ọkọ̀*** *ìgbadgbọ́ wọn*
>
> —1 Timotiu 1:18:19

Pàtàkì jùlọ, àwọn ènìyàn ti wọn sé ọkàn ara wọn le lati má tẹ́tí sí ohùn ẹ̀rí-ọkàn wọn ti sọ agbára làti má sètọ́ni ayè wọn nù. Atọ́ka-ọ̀na wọn ni wọn ti bàjẹ́ tí kò sì le sísẹ́ mọ́. Wọn ò le sọ ibi ti wọ́n nlọ. Paulu ni a ni lati máa ni ẹ̀rí-ọkàn rere, eyìí ti o mọ́, ki a le ri dájú pe à niìn ni ọ̀nà tótọ́. Nitori a le sẹ́ ọkàn wa le àti ba agbára lati se ohun ti o tọ́ àti se àitọ́, Paulu ni o se pàtàki lati máa tèlé òfin àti se ohun ti ọ tọ́.

*"Nítorínà, ẹ̀yin kò gbọdọ̀ saìmá tẹríba fún àsẹ, kì íse nítorí ìbínú nìkan sùgbọ́n nítorí ẹ̀rí-ọkàn pèlú"* (Romu 13:5).

Ti o ba saìgbọ́ràn si òfin, ẹ̀rí-ọkàn rẹ yóò ma dá ọ lẹ́bi. Torinà, Paulu ni kí ẹ tẹriba fún òfin, lati ma se ohun ti ó tọ́, ki ọkan rẹ ba le wa ni ìsínmi ki o si le máa se bi Ọlọrun ti sètò silẹ̀ lati máa se, ki o sì dábòbò bò ọ́ kúrò lọ́wọ́ ewu.

Niti ẹ̀ri-ọkàn, Mo tún le rántí ìwa òmúgọ̀ kan ti mo hù ti yóò se àpèjuwe òfin yìí. Ìsẹ́lẹ̀ yìí ti sẹlẹ̀ kin tó bẹ̀rẹ̀ si ni se iṣẹ́ ìrànṣẹ́. Wàá rí idí ti

Ọlọrun kò se gbà ki nti ma se iṣẹ́ ìrànṣẹ́ nà nigbàti ó ba gbọ́ ìtàn yí. Ìtàn yìí dá lé ọkọ àkọ́kọ́ ti mo ni. Ọkọ̀ pijọ́ 505 ni ọkọ̀ nà ti mo tún nifẹ́ sí. Óda, ni ọjọkan ọmọkúnrin kan kọlù mi lati ẹ̀hìn ọ si fọ́ ina ọkọ̀ mi lẹ́yìn. Ẹ̀hìn mọ́ tò mi tẹ̀ sínú firamù rẹ̀ si tẹ̀, àwọn nkan miràn nà bàjẹ́ ni ara ọkọ̀ àràkunrin nà nitorí ijàmbá ti ó sẹlẹ̀.

Àwọn ile iṣẹ́ adójútòfò ti ọmọkúnrin ti ó kọ́ lu mọ́tò mi nà wá si ahéré wa lati wá wo ọkọ̀ na àti sọ iye ti ó máa ná wọn. Kin tó sọ nkan ti ó sẹlẹ̀ nigbà ti wọ́n dé, mo ni lati jẹ́ ki ó mọ pé ni bi ọ̀sẹ̀ melo saájú ki ìjàmbá to sẹlẹ̀, ni ẹ̀yà ara ọkọ̀ na tin yọ sọnù. Aporùn mọ́tò, ti o wà lẹ̀hìn mọ́tò na kò siṣẹ́ mọ ni ọ̀sẹ̀ diẹ ki àwọn asojú to wà lati se ìṣẹ́ ti wọn. Nigbati àwọn asojú ti ile iṣẹ́ adójútòfò se àyẹ̀wò tan lorí ọkọ̀ nà, o wá bi mi lérè boyá kin ni ìbòrí ti o ti já kúrò ti o wa nílẹ̀ lẹ́gbẹ ọkọ nà pẹ̀lú ninú ìjàmba nà, ẹ̀ri ọkàn mú mi nigbàti mo sọ pé bẹ́ẹ̀ni tàn, ó tun bèrè pé se ara rẹ̀ na ni aporún ti o ti sí kúrò nà, Mo tún ni "Bẹ́ẹ̀ni."

Ni inú ẹ̀mi mi lọ́hún, mo gbọ́ ti ẹ̀rí-ọkàn mi npariwo, Gray, kin ni nkan ti ó nse yìí? Ò nparọ́" Nibayìí, gbọ́ bi mo ti tan ara mi. Mo tilẹ̀ ranti bi mo ti ronú ti mò nbá ara mi sọ̀rọ̀ pé ma kọbi ara si ohùn nà, mo nsọ fún àrà mi pé o ma to lọ. Loní, mi o le gbàgbọ́ pe mo ronú ni àwọn ọ̀nà wọ̀nyìí nigbànà. Wo se inú rẹ kò dún pé mi kò ti ma se Pasitọ̀ ìjọ nigbànà? Mo mọ̀ dájú pe ínú Ọlọrun dùn'

Lọ́nàkàn, wọn gbé ọkọ̀ lọ si ibiti wọn o ti túnse. àti ni àrin ọ̀sẹ̀ kàn sí ìgbàna wọ́n pè mi kin wá gbé ọkọ̀ mi. Bi mo ti rí mọ́tò mi ní ilé iṣẹ́ àwọn ti o ntúnse, inú mi dùn gan. mo jẹ́ pípé. Mo wa mọ́tò mi lọ sílé, inú mi dùn si ohun gbogbo ti wọn ti ba mi túnse. Lẹ́hìn bi ọ̀sẹ̀ kan si tàbi si ìgbà diẹ mo pinnu lat lọ si ilé ki le jẹ̀ ounjẹ ọ̀sán pẹ̀lú Drenda àti àwọn ọmọ. Ahéré wa kò ju bi máilì meji lati ofisì mi ti mo gbà lati ma fi siṣẹ́ lórí ọ̀rọ̀ ti ìsúna lọ. Mo si kúrò ni òpópóna mo si gbé ọkọ̀ nà dúró si ẹ̀gbẹ́ ilẹ̀kùn wájú ile, mo wọle lọ, mo si lọ́ gbàdùn ounjẹ ọ̀sán mi.

Bi mo ti fẹ́ kúrò ni ile ti mo sì njade lọ sí iwáju ile, mo sàkíyèsí pé ko si ọkọ̀ mi nibẹ̀ mọ̀. Órú mi lójú. Ibo ni ọkọ̀ mi lọ? Mo wo àyiká mo wa ríi. Ori óke ni ilé wá wà, o le jẹ́ wipé mo gbàgbè lati fijánu ọkọ̀ mu. Mi o si se bẹ rí, ti o bá jẹ́ pé mo má nse bẹ́ẹ̀ ni kò ba ti fẹ̀yìn rin já òpópóna ti yóò si lọ kọlu igi. Bi mo tin lọ sí ibi ti ọkọ̀ na wà, nse ni ẹ̀rù nbámi, Ẹ̀hìn mọ́tò tun ti bàjẹ̀, jú bi o ti wa tẹ́lẹ̀ ju kin tó túnse lọ, faremu nà tún ti tẹ̀ si bi o ti wà tẹ́lẹ̀,

ìborì na ti já danu, bẹ́ sì ni aporùn nà kò tún siṣẹ́ mọ, Ohungbogbo padà si bi ó ti wà tẹ́lẹ̀ ki wọn to gbé mọ̀tò lọ fún túntún se ni gbà ti o fi ni ijàmbá ọkọ̀.

Bí mo ti dúró sibẹ̀, lojiji, ni ó wá si ìran mi , mo sì bẹ̀rẹ̀ si ni rẹ́rín. Ọlọrun nkọ mi ní ẹ̀kọ́ ni, awọ́n ẹ̀kọ́ ti omodekùnrin oniwáasù yìí nilò ki ó to lọ ma dárí àwọn ènìyàn. Mi o tún ọkọ̀ nà se rárá, mo lọ tàá ni bi o ti se wà. Mo sì tún le ránti ọkàn si ni ìgbesí ayé mi, ni ibiti ẹ̀rí-ọkan mi tún ti pariwo mọ mi pé dúró kin ni nkan ti ò nse. Mo pèé ni ìtàn kẹ̀kẹ́.

Mo lerò pé awọn itàn wọ̀nyìí nràn ọ́ lọ́wọ́. Mo mọ̀ pé o kò lérò pé mo le se irú àwọn nkan wọ̀nyìí, sùgbọ̀n o nse àsìse, inú mi kàn dùn pé mo ri ìgbàlà nitori mọ mọ̀ pé ayé mi kò ba di irú mi ni bi kò bá se pe mo rí ìgbala.

Ìtàn kẹ̀kẹ́ sẹlẹ̀ ni bi ọdún díẹ̀ sẹ́yìn, mo sẹ̀ṣẹ̀ sọ fún yin, bẹ́ si ni, mo sẹ̀sẹ̀ bẹ̀rẹ̀ iṣẹ́ ìrànṣẹ́ ni ẹ̀ka ìjọ wa tuntun. Mo si nlọ si ilé baba mi ni ọ̀sán ọjọ́ Satide ti wọn ngbé ni ẹ̀yìnkùle Silver Dodge Caravan si ọ̀nà òpópónà meji ni àdugbò ti baba mi ngbé. Ile baba mi wa ni abẹ́ òkè ni apá òkè mejeji ni ibi tí wọ̀n ngbé. Fun àwọn idi kan, mí ò rí onikẹ̀kẹ́ yí pé ò nbọ̀ lati orí òkè, èmi ti nrọra jade lọ oun sí wà lẹ́yìn mi, sùgbọ́n nitorí pe oun na bọ lati òkè ni, o sare ba mi ni dédé igbà ti mo fẹ́ yi ọwọ́lati sún sì wajú.

Nigbogbo àsìkò yi mi o tilẹ̀ mọ̀ pé ó nbọ̀ lẹ́yìn, lojiji mo kan gbọ́ ariwo BAM, BAM, BAM, ni ẹ̀gbẹ́ ọkọ̀ ẹrù mi ni, mo sare wo gilasi ti o wà lẹ́gbẹ́, nibẹ̀ ni mo ri onikẹ̀kẹ́ lẹ́yìn ti o gbé ọwọ́ soké ti o bẹ̀rẹ̀ si nibú ebú, o bi mi ninú pé se o yẹ ki onikẹ̀kẹ́ se bo ti se ni, mo mọ̀ pé ko ba duró ki o si rọra ma rinbọ lati òrí òkè ti o siri wipé ẹ̀yìn ni èmi kọ, mo si mọ ti o ba fẹ́ lati yípo gba ẹ̀gbẹ́ kó ba se bẹ́, sùgbọ́n o kọ̀ lati se bẹ̀ o si kọlú mi.

O bimi ninú gan, mo si rò pé ò nilò kin kọ lẹ̀kọ́, mo wa rọ̀ra duró diẹ̀ ti o fi súnmọ́ ọdọ̀ mi, mo tẹ bireki(ijánu) ọkọ̀, inú mi dùn bi mo se ríi ti o ndura lojiji ki o ma ba kọlú ọkọ̀ mi mọ̀, o wá n se ràbàràbà lọ lojú títì, ti nse nkan mi o rí tàbi gbọ́ ri, nise ni o nlọ titi.

Mo wá rọra nwakọ̀ mi lọ lojú titì, ọkọ̀ mi si kọjú si ọ̀nà, ti o joko ni ìgun kan, ti mo nwo onikẹ̀kẹ́ ti o nbọ̀ ni ọ̀na ọdọ̀ mi. Bi o ti ri pé mò nduró de on, o wo ọkọ̀ mi, lojiji o dakẹ́ jẹ́. Mo lero wipé ó ti mọ pe ọri kẹ̀kẹ́ ni on wà ati wipé ọkọ̀ tóbi ju kẹ̀kẹ́ lọ, Mo sí ferésé ọkọ̀ mo wá duro dèé ki o fi sún mọ ọ́dọ́ mi. Bi o ti súnmọ mi ni ibiti mo duró sì mo sọ fún pé ti mo bat un pada ri no ojú ọ̀nà yìí lẹ́ẹ̀kansi, ma kọlú bi mo ti nsọ èyí ni mo gbà àrà

ọkọ̀ nà, ni àsikò yi o tó bi ìwọ̀n bata mẹ́dògún si mi. Mo lero pe ọkọ̀ ti ha nkan lara kẹ̀kẹ́ rẹ, mo kan mọ̀ ni, mo sir o pe orí ló kó mi yọ. *Mo lérò pé mo fi ja lójú* sùgbọ́n kó pẹ́ lọ tító.

Lati inú ẹ̀mi mi, Ẹ̀mi mimọ̀ fi kọ si mi, mo gbọ́ ti Ẹ̀mi Mimọ́ nsọ pẹ̀lú ohun àṣẹ wípé "Gary kin ni o nse?" mo kan nrí àwọn ọ̀rọ̀ yìí bi pé ko si oòtọ́ ninú wọn ni àkókò nà. Lojiji, ni ó wa si oye mi pé mi o bá ti pa arakunrin nà o, mo wa lọ wòó mo ri ti o nrọra nrìn, ó tẹri mọlẹ̀, o nwò bi ẹniti o farapa tabi tun wòó pé oun tun wà làye. Mi o mọ̀ dajú pé bí mo ba nwakọ̀ lọ ni ọ̀nà nà pé ẹ̀ri-ọkàn mi yóò fí mi silẹ̀. Bi pasitọ ti o sẹsẹ̀ bẹ̀rẹ̀ ìsẹ́ ìránṣẹ́, mo wa rí nkan ti kò bá, mo nwò awọn ìwe ìròyìn tì wọ́n nkọ́ àkọlé pé "Pasitọ Ìjọ Faith Life ni ó kọlu onikẹ̀kẹ́ kan ninú ijàmbà ti o sẹ́lẹ̀ lójú ọ̀na" Ẹ̀mi Mimọ́ wa rán mi létí pé nitori irú àwọn ènìyàn bayìí ni on se pé mi lati bẹ̀rẹ̀ ìjọ ni agbègbè wa. Ìwa ti èmi gban wù o bàmilẹ́rù, mo si lọ si ìrònúpìwadà niwaju Oluwa pẹ̀lú omijé lojú.

Ò yá, jẹ́ kí a wòó pé, lóòtọ́, ni o gbọ́ ohùn ti Ọlọrun tilẹ̀. Sugbọ́n o si fẹ̀ pa ẹ̀rí ọkàn nà mọ́ ni jẹ́jẹ́ o kò fẹ̀ kí o le ki ó bá le ma gbọ́ ohùn Ọlọrun nigbàgbogbo. Bibeli sọ wipé àwọn ara Israẹli si se ọkàn wọn le si Ọlọrun wọn kó sì le dé Ilẹ̀ Ìlérí na. Ẹni ti ó kọ ìwe Heberu ti kìlọ̀ fún àwa, onigbàgbọ́ ti Majẹ̀mu Tuntun, ki a ma se tẹ̀lé àpẹẹrẹ wọn.

> *Nítorínà gẹ́gẹ́ bi Ẹ̀mí Mímọ́ ti wí, Lónìí bí ẹ̀yin bá gbọ́ ohùn rẹ̀, Ẹ máse sé ọkàn yín le, bí ìgbà inúnibíni, bí ní ọjọ́ ìdánwò ní aginjù.*
>
> —Heberu 3:7-8a

Bi ẹ̀ mẹta ni a sọ́ ọ̀rọ̀ ìkìlọ̀ yìí ninú ori kẹta àti ori kẹẹrin. Kíló fa ìkìlọ̀ yìí? Nitori ti Ọlọrun fẹ́ bùkún ọ o sì fẹ́ ki ó ni ohun gbogbo ti Jesu ti san gbèsè rẹ̀.

Bi ẹniti ọkàn rẹ̀ le, ó mú mi ranti ẹsin kékeré ti mo ni nigbà ti mo wa ni ọ̀dọ̀. Ó jẹ́ ẹrankò ti o burú ti ó sì gbọ́n bákanna. Èmi nikan ni o le gùn, tàbi kí nsọ pé ti ó tóbẹ̀ lati gùn. Mo ranti pé ni ọjọ́ kàn, mo ni ọ̀rẹ́ kan tí òun na sọ pé on fẹ́ràn ẹsin kò sì sí ẹsin ti on kò le mu. Ó sa tẹnumọ́ọ pé òun le gun Tony, ẹsin (orúkọ̀ ti mo sọ ẹsin nà niyìí). Nígbàti ó ya, o sa jẹ́ ki o yé mi pé ki njẹ́ ki òun gbìyànjú lati gun ẹsin nà. Jackie ni orukọ ọmọkùnrin nà, mi o sì le gbàgbé ohun ti ó ṣẹlẹ̀ nígbàti o gun ẹsin nà. Nigbàti ó jọkò sórí Tony

tán, bẹ́ ni wọn gbéra ti wọn lọ́. Tony gbéra ti o nsaré lọ si ibi odò adágun kan ti o tó ìwọ́n ààdọ́tà ibùsọ̀ lati ile wa. Jaẹkie bẹ̀rẹ̀ si ni fa ìjánu rẹ̀ kikan kíkan ki o bá le duró, Tony kò kọbi ara si rárá. Dípò kí, o dúró, o sáré si ibi ọmi adágún na lojiji ó dúrò o bẹ̀rẹ̀ ori rẹ̀, o súnmọ eti omi, kinni o sẹlẹ̀ Jackie já sinú omi adágun nà ni tààrà. Tony pẹ̀yìnda ò bẹ̀rẹ̀ si ni jẹ àwọn koríko lẹbá odò bi ìgbà ti nkankan kò sẹlẹ̀.

**"NITORÍNÀ, GẸ́GẸ́ BI Ẹ̀MI MIMỌ́ TI WÍ, 'LONÌÍ, BÍ Ẹ̀YIN BÁ GBỌ́ OHÙN RẸ̀, Ẹ MÁSE SÉ ỌKÀN YÍN LE, BÍ ÌGBÀ ÌMÚNIBÍNÚ, BÍ NÍ ỌJỌ́ ÌDÁNWÒ NÍ AGINJÙ."**

**HEBERU 3:7-8A**

Sé o wá rí, wọn ti yan Tony fún ọ̀pọ̀ ìgbà ti o fi jẹ́ pé ti ẹ bá ti yan diẹ kó palára ni ẹnu rẹ̀ mọ́. O ti mọ́ ọ lara de ibi pe ti ẹ bá nfa ìjánu rẹ̀ ko le dùn mọ̀. Niti ẹsin yìí, Tony wà lásán laise ànfàni kan fún ẹlomiran ju èmi nikan lọ. Kilóde? Nitori, bi mo ti sọ, ó gbọ́n gan. Èmi nikan ni ó nfún lounjẹ. Ohunkàn ti o si mọ̀ ni ọ̀nà kan ti mo fi ngbe jade kurò ninú ile rẹ̀ lati lo gba afẹ́rẹ́ àti lọ́ jẹ eweko ti o fẹ́ràn lati máa jẹ́ ti mo ba ti gún lọ síbẹ̀. sibẹ̀ mo ni lati ma sọ́ ọ. Ó ma nrin pẹ̀lú mi yó tẹ ori rẹ̀ si ẹ̀gbẹ̀ kan yó si ma wò mi bi mo ti ngún lọ. Ó nretí ki ngbé oju mi si ẹ̀gbẹ̀ kejì. Nigbanà ni yó tètè gbo ri rẹ̀ padà àti fẹsẹ̀ rẹ̀ ta mi. Jẹ kin sọ fún ọ pé ó má ndùn mi, nitorinà ni èmi nà ma nkiyési. Sùgbọ́n ti a bá sọ pè ó wulò, kò wúlò,

Ti à bá fi ayè gba ọkàn wa ki ó le, a ó ni wulò fún Ọlọrun, gẹ́gẹ bi Tony. Ni àsikò kan, a sọ Tony mọlẹ̀ ni ìta pẹ̀lú ẹ̀wọ̀n. Baba mi ma nda omi sinu pali fún Tony ni. Nigbati baba mi yi padà lati máa lọ. Tony si lọ kan wọn lati ẹ̀yìn, baba mi kò ti di ẹni ìgbala, wọn si ma nbinú. Àpò iyọ̀ kan wa lẹ́gbẹ̀ kan ti kò jina si ibi ti pali omi nà wà, baba mi gbé àpò iyọ̀ nà ó si jùú lú ẹsin na. Súgbọ́n Tony yèé. Se mo ni ìgbàgbọ́ ninú Tony? Láìlái!

Bi o si ti ri ninú àye àwọn ènìyàn niyìí. Wọn rò pé àwọn le saìgbọran, ki wọnse ohun ti ó tako ẹ̀rí-ọkàn wọn lẹkan soso yìí, Sugbọn ohun ti wọn kò mọ́ ni pé nise ni wọn nda ọgbẹ́ sinú wọn nigba kugbà ti wọ́n bá se é èyí. Ni ọjọ́ kan wọn yóò wa dàbi ti Tony ti kò mọ irora mọ́ tàbi rò ó wò nigbàti wọn ba yàn lati saigbọràn si Ọlọrun tàbi lati se ohun ti Ó sọ. Àtunse ni kí o tètè ronúpìwàdà nigbàti o ti mọ̀ pé o tit a ẹ̀rí-ọkàn rẹ nù.

Orin Dafidi 51 Ọba Dafidi ni ó kọ ọ́ lẹ́yìn ìgbàti ò dẹ́sẹ̀ pẹ̀lú Batisebà.

Plsaamu ìrònúpìwàdà ni.

> *Ọlọrun sàánú fún mi gẹgẹ bí ìseun ìfẹ́ rẹ, gẹ́gẹ́ bí ìrònú ọ̀pọ̀ ànú rẹ, nu ìrékọjá mi nù kúrò. Wẹ̀ mí ni àwẹ̀mọ́ kúrò nínú àìsedédé mi, kí o si wẹ̀ mi nù kúrò nínú ẹ̀sẹ̀ mi. Nítorí ti mo jẹ́wọ́ ìrékọjá mi nígbàgbogbo ni ẹ̀sẹ̀ mi sì mbẹ níwajú mi ìwọ nìkansoso ni mo sẹ̀ sí, ti mo sì se buburú yìí nímwamjú rẹ; kí a le dá ọ láre, nígbàtí ìwọ bá nsọ̀rọ̀, kí ara rẹ kí o le mọ́, nígbáti ìwọ bá ńse ìdájọ́. Kíyèsi i nínú àìsedédé ni a gbé bí mi; àti ninu ẹ̀sẹ̀ si ni ìyá mi sì lóyún mi. Kíyèsii ìwọ fẹ́ òtítọ́ ní inú; àti níhà ìkọ̀kọ̀ ni ìwọ o mú mi mọ̀ ọgbọ́n. Fi ewé- híssópù fọ̀ mi èmi o si mọ̀; wẹ̀ mí èmi ó sì fún ju ẹ̀gbọ̀n–owu lo. Mú mi gbọ́ ayọ̀ ati inu dídùn ki áwọn egungun tí ìwò ti run kí o le máyọ̀. Pa ojú rẹ mọ́ kúrò lára ẹ̀sẹ̀ mi kí ìwọ kí o si nu gbogbo àìsedédé mi nù kúrò.* ***<u>Da aya titun sinu mi,</u>*** *Olorun ki o si tun okan didurosinsin se ninu mi. Mase sa mi ti kuro niwaju re, ki o ma sigba Emi Mimo re lowo mi. Mu ayo igbala re pada to mi wa; ki o fi emi ominira re gbe mi duro.*
>
> —Orin Dafidi 51:1-12

> *Nítorí ìwọ kò fẹ́ ẹbọ, tí èmí ìbá rú u; inú rẹ kò dùn sí ọrẹ-ẹbọ sísun. Ẹbọ Ọlọrun ni ìròbìnumjẹ́ ọkàn; ìróbìnújẹ́ àti ìrora àyà, Ọlọrun, òn ni ìwọ kì yóò gàn.*
>
> —Orin Dafidi 51:16-17

Dafidi nkígbe si Ọlọrun lati da àyà títun sinú rẹ́, 'mi ti o tí wó palẹ̀, ọkan ìrònúpìwàdà. Pàápá jùlọ Dafidi nsọ̀ pé òun fẹ́ ọkan ti yóò le mọ̀ lẹ́ẹ̀kansi. Sugbọ́n Dafidi kò ba ma ba ara rẹ̀ ninú wahálà yìí ti o ba jẹ́ pé ó gbọ́ràn si ẹ̀rí-ọkàn rẹ̀. Torinà, ti o ba ti nyan ẹ̀rí-ọkàn rẹ jẹ, wa ma sẹ́ ọkàn rẹ le, yóò si rọ̀ ọ́ lọ́rùn lati tun se nigbà miràn, wa tun se nigbàmiràn, igbàmiràn, ti o kò fi ni gbọ́ ohun Ọlọrun mọ̀ rárá.

Ẹ̀ri-ọkàn jẹ́ ọ̀nà kan ti à ngbà gbọ́ ohun Ọlọrun. bẹ́ẹ̀ni, Ẹ̀mi Mimọ́ si nba wa sọ̀rọ̀ pẹ̀lú ìtọnisọ́nà àti ìdari. Ati bi mo ti sọ, Mo ti gbọ́ ri ti Ẹ̀mi Mimọ́ ba mi wi pẹ̀lú ariwo, ti ó npàṣẹ ninú ohùn rẹ̀ kẹ́lẹ́, kékeré. Mo ti gbọ́ tí Ó nsọ̀rọ̀ nipaṣẹ́ àlá àti ìran bàkannà, Ti ma sitún sọ́rọ́ le lórí ninú orí

ti o kàn. Sùgbọ́n ninú ori yìí, à ti kọ́ bi a ti se le gbọ́ohun Ọlọrun, a nilò lati pa ẹ̀ri-ọkan wa mọ kuro ninú àwọn ẹ̀sùn àti kí a tètè ma lọ́ si ìrònúpìwàdà lati le pa wọ́n mọ́ ni ẹlẹgẹ́ àti ni tútù ki a bà lé gbọ́!

ORÍ KẸWÁ

# ÀWỌN ÌRAN ÀTI ÀLÁ

Lójiji ni mo dìde joko lórí ìbùsùn mo si sọ fún Drenda pé, "o lóyún, ọmọbinrin ni wàá si fi bí!"

Ninú gbogbo ọmọ máràrún ti a bí ọ̀kansoso ni Ọlọrun fi iru ọmọ ti yóò jẹ́ hàn mi—Polly, ni ẹlẹ́kẹrin. Mo si gbàgbọ́ pé ó rí bẹ̀ ki a bà le gbàá nitori ti ẹbi wa ni ìjàmbá ọkọ̀ ni àsikò ti Drenda wà ninú oyún osù mẹ́fà ni, oyún Polly. Ti à sì nlọ si ìrìn àjò mailì máàrùnlénúàdọ́tà ni wakatí kan ni òpópóna ọlọ́nà tóóró mejì, ọmọkùnrin kan sì jánà niwájuú wa. Kò si àyè lati dúrò mọ́, ti a sì kọlu ọkọ̀ rẹ̀. Ko sí ẹni tí o farapa, sugbọ́n gbogbo wa ni a gbé lọ si ilé ìwòsàn. Drenda, nitìrẹ̀, nitorí pe o ni oyún, tí ìgbànú ti o fi dábòbò ara rẹ̀ lorí ijoko si pá lara díẹ̀ àti ni ipá díẹ̀ lori ikùn rẹ̀. Ohun ti ó kàn án ni ọmọ inú Polly. Nitorí Ọlọrun ti sọ́ fún wa nipa Polly, à si wa fọkan wa balẹ̀ pé kó sí nkan ti o se Polly.

Ọ̀rọ̀ lorí Polly, mo si rántí, nigbati Polly bi ìyàwo, tí ó ní oyún ọmọ rẹ̀ àkọ́kọ́ bi ìyawó. Èmí àti Drenda jade lọ kúrò ni orilẹ̀-èdè wa fún ìrìn -àjò isẹ́. Lairò tẹ́lẹ̀, àsikò ati bímọ Polly ti tó ni àrin ìgbàti a wà ní ìrin àjò nà. Tí o ba mọ ìyàwó mi, Drenda, kò ni fẹ́ lati pádanù ọ̀kànkan ninú àwọn ọmọ obinrin rẹ̀ ni igbà ìrọbi. A wá ngbé yẹ̀wò boyá ki a pa irin àjò na tì nà. Mo lọ lati gbàdúrà lórí rẹ̀, Ẹ̀mi Mimọ́ si sọ fún mi pé, ọjọ́ bíbí rẹ̀ kò tí ì yá, pé ni ọjọ́ keji ọjọ́ tí a bá padà de ile ni yòó bimọ, Mo sì sọ ohun ti Ọlọrun sọ nipa ọjọ́ tí yóò bímọ fún un, a sì tẹ̀síwáju lílọ sí ìrín ajò wa. Nigbati a padà si ilẹ̀, ọmọ si bẹ̀rẹ̀ si ni múu ni ọjọ́ gàn ti Oluwa wí. Igboru ọmọ ọmọ wa obìnrin ti a ṣẹ̀ṣẹ̀ bi, wá sáyé ni àkókò ti ó tọ́.

Ara àwọn àpẹẹrẹ pé Ẹ̀mi Mimọ́ nbá wa sọ́rọ̀, nipa àwọn nkan to nsẹlẹ̀ ni ayé nìyìí, pẹ̀lú awọn ọ̀rọ̀ Ẹ̀mi Mimọ́ ti ó nti inú ẹ̀mí rẹ jade wá. Bẹ́ẹ̀ni

àwọn ọ̀na miràn tún wa ti Ẹ̀mi Mimọ́ fi nba wa sọ̀rọ̀ ti ó yẹ ki a kíyèsi.

> *Yóò sì se níkẹhìn èmi o tú ẹ̀mí mi jáde sí ara èniyàn gbogbo, àti àwon ọmọ yín ọkùnrin àti àwọn ọmọ yín obìnrin yóò ma sọtẹ́lẹ̀, àwọn arúgbo yín yóò ma lá àlá àwọn ọ̀dọ́mọkùnrin yín yóò maa ríran. Àti pẹ̀lú sí ara àwọn ọmọ ọ̀dọ̀ ọkùnrin, àti sí ara àwọn ọmọ-ọdọ́mọbìnrin, ni èmi o tú ẹ̀mí mi jáde ní ọjọ́ wọnnì.*
>
> —Joeli 2:28-29

Wòlli Joẹli sọ wipé ọjọ̀ nà mbọ̀ nigbàti Ọlọrun yóò tú Ẹ̀mi rẹ̀ jáde sara gbogbo ènìyàn. Ati ngbé ni àsikò nà bayìí, Ni ọjọ́ Pentikọsti, Ẹ̀mi Mimọ́ wa bà lé gbogbo àwọn ti ó wà ni yàrá òkè. Gbogbo ìjọ èniyàn ni o rí gbogbo àwọn ti o wà ni yàra òkè ti wọn nfi èdè titun sọ̀rọ̀ ti wọn yin Ọlọrun lógo, wọn rò pe wọn ti mútíyó ni wọn si nberè pé, “Kin ni èyí?" Peteru duró lati ba ìjọ àwọn ènìyàn nà sọ̀rọ̀.

> *Sùgbọ́n Pétérù didde dúrom pẹ̀lú àwọn mọkànlam ìyomkù, ó gbé ohùn rẹ̀ sóke, ó si wim fún wọn gbangba pé, Ẹ̀yin ènìyàn Judea, ati gbogbo ẹ̀yin tim ngbé Jerúsálẹ́mù, ki èyimyi kí ó ye yin, ki ẹ sì fetísim ọ̀rọ̀ mi. Nitorim àwọn wọ̀nyìí kò mutíyó, bí ẹ̀yin ti fi pè, wákàti kẹta ọjọ́ sá ni èyí sùgbọ́n èyí ni ọ̀rọ̀ ti a ti sọ láti ẹnu wòli Joẹ̀li wá pe; Olorun wipe, “ Yóò sì se níkẹhìn èmi o tú ẹ̀mí mi jáde sí ara ènìyàn gbogbo, àti àwon ọmọ yín ọkùnrin àti àwọn ọmọ yín obìnrin yóò ma sọtẹ́lẹ̀, àwọn arúgbo yín yóò ma lá àlá àwọn ọ̀dọ́mọkùnrin yín yóò maa ríran. Àti pẹ̀lú sí ara àwọn ọmọ ọ̀dọ̀ ọkùnrin, àti sí ara àwọn ọmọ-ọdọ́mi ọbìnrin, ni èmi o tú ẹ̀mí mi jáde ní ọjọ́ wọnnì wọn ó sì ma sọtẹ́lẹ̀. ’ ”*
>
> —Ìse Àwọn Àpọ́stéli 2:14-18

Ìran àti àlá jẹ́ ara ọ̀nà kan ti ó tóbi tí Ẹ̀mi Mimọ́ ngbà bá wa sọ̀rọ̀. Mi o mọ idi tí Ẹ̀mi Mimọ́ fi ma sọ̀rọ̀ ni kẹ́lẹ̀kẹ́lẹ̀ ni ìgbà miràn,ohùn kékeré, ni àwọn ìgbà miràn Ó sọ̀rọ̀ ninú àlá. Mo rò pé àra ìdáhùn rẹ̀ nipé gbogbo wa ni kò ráyè. Nigbati à bá dákẹ́ yóò le ba wa sọ̀rọ̀. Tàbi o le jẹ́ pé ni irú ipò tó

rújú tàbi àwọn àyídayidà ni o fa tí o fi le lati gbọ́ ohùn rẹ kẹ́lẹ́ kékeré, Ẹ̀mi Mimọ́ fẹ́ rí dájú wipé à gbà ifiràǹsẹ́ nà. Niwọ̀n ìgbà ti àwòrán kan tó ẹgbẹ̀rún àwọn ọrọ̀. Ohunkohun ti o le fàá, mo dupẹ̀ lọ́wọ́ Ọlọrun fún àlá àti íran. Àwọn àlá àti ìran jọ ara wọ́n. Àwọn mejeji ni àwòrán ti à nrí, orísirísi ènìyàn ni o nriran nigbati wọn kò sùn, àti pé àwọn àlá ni awọn àwòran ti a nrí ti a bá sùn.

Ni ti ìran, díẹ̀ ni ma pé ni àwọn ìran sísí, ninú èyíti ó jẹ́ wipé o kò sùn ò sì nri àwọn ìran kan bi igbàti o nsẹ́lẹ̀ ni tóotò. Awọn ìran ti ò ni ìtumọ jùlọ ti mo ti rí ni nigbàti à pé mi lati wàásù ni ọmọọdún mọkandinlogun. Mo sẹ́ṣẹ́ gba ìrìbọmi ti Ẹ̀mi Mimọ́ ni kò ti ju bii osù kanlọ ki ó tò sẹlẹ̀. Lóòtọ́, gbogbo rẹ̀ ni o jẹ́ nkan titun si mi nitori ìjọ eléto ti mo nlọ tẹ́lẹ̀ wọn kò kọ wa nipa ìrìbọmi ti Ẹ̀mi Mimọ́ lọ tító.

Sugbọ́n, ọjọ ìbí mi ni, wọn si pé mi si ibi ase alẹ́ pẹ̀lú àwọn ọ̀rẹ́ mi kan. Bi ati joko ti a njẹun. à ti dupẹ́ lorí ounjẹ na. lojiji, mo kan rí pé Ẹ̀mi Mimọ́ bà le mi ni pẹ̀lú ọwọ́ agbára. Lẹ́ẹ̀kansi, mo sẹ̀sẹ̀ mọ nkan wọnyìí ni, Sugbọ́n mo mọ̀ pé ti o ba ti gba ìrìbọmi ti Ẹ̀mi Mimọ́ ohun ti o kú ni kí Ẹ̀mi Mimọ́ ma lò ọ. Mi o mọ ohun ti ò kàn ti má se ni àsikò na, mo wa bèrè pé ki wọn fún mi ni ayè dìẹ, mo jade sita, bi mo ti bọ́sita tàn.

Mo jáde sita, bẹ̀ẹ́ni, agbára ìwàláyè Ọlọrun pọ̀ si, mo wa ri ìran ọ̀run, ti o túmọ si pé lóòtọ́ ni mo rí àwọn nkan yìí, ti ó wa dà bi ẹni pé nkan ti o nsẹ́lẹ́ bi mo ti se nri ni ni ọjọ́ na. Mo ri wipé mo duró ni ẹ̀yìn ẹ̀rọ gbohùngbohùn kékeré kan, mo si nba àwọn èniyan sọ́rọ́ ninú yàra nà, Ninú yàra ná àwọn ti o wà nibẹ̀ tó márùndinlógóji si ogóji ènìyan ninú rẹ̀ gbogbo wọn joko lórí àga. Mo le sọ pé alẹ́ ni nitori lati ojú fèrésé mori pé okùnkun kùn ní ìta.Ohùn kan wá o sọ pé "Mo npè ọ́ lati máa wàásù Ọ́rọ̀ mi" Ẹ̀ mẹta ni o sọ ọ̀rọ̀ nà léra wọn lẹ́yìn na mi o ri àwòrán nà mọ́ ti ara mi si lelẹ̀. Bi mo ti padà si inú ilé, àwọn ọ̀rẹ̀ mi bi mi lere wipé kin ni ó de, mo dahún pé, mo lérò pé a pè mi lati wàásù ni!"

Mo ranti pé bi mo ti delé ni alẹ́ ọjọ̀ nà ni mo sọ fún baba mi ohun ti ó sẹlẹ̀. Ó wa sọ fún mi pé àwọn oniwàásu kì ní owò lọ́wọ́. Gbogbo ohun ti baba mi sọ nìyìí. Baba mi ki se Kristiani bẹ́ẹ̀ nà, sùgbọ́n o ma nyìn Ọlọrun, o fi ayé rẹ fún Jesu ni ẹni ọgọ́rin ọdún o si ti lọ sinmi bayi ni ọ̀run.

Torí idi èyí mo gbàgbọ́ pe Ẹ̀mi Mimọ ba mi sọ̀rọ̀ ninú ìran àwọn ọ̀run nitori, ni àkọ́kọ́, ọmọde ni mi. O mọ pé ọ̀pọ̀lọpọ̀ inúnibíni ni ma bà pade

ninú ẹbi mi nitorí ti mó nsin in àtipé mo nilò ìdákọró nà fún ìrìn àjò tí nbẹ niwájú Bẹ́ sì ni ìran yìí si ba mi sọ̀rọ̀ latí ìgbànà lọ.

Iran miràn ti mo tún rí ni ó wáyé ní ahéré ti a ti gbé ri. Ati gbé ni ahéré ti o ti gbó yìí rí, ó to bi ọdún mẹ́sán tí a fi gbé inú ahéré yìí, ni gbogbo àsikò nà ni à wà ninú ìṣẹ́/àìní. Sùgbọ́n a bẹ̀rẹ̀ si ni kọ́ nipa bi ìjọba Ọlọrun ti nsiṣẹ́, à si bẹ̀rẹ̀ si ni ni láári tití a fi san gbogbo gbèsè ọrùn wa tán pátápátá .

Ni àsikò yìí gàn ni Ọlọrun wa mú ìran ti mo tí rí nigbatí mo wà ni ọmọ ọdún mọ́kàndínlógun nigbàti ó pé mi pé lati máa waasù. Ni àkókò yìí gàn lẹ́yìn ọdún kọkànlélógún ti o ti pé mi lati wàásù, ti Ọlọrun sọ fún mi lati bẹ̀rẹ̀ ìjọ. kí ó tó di ìgbà nà, mo ti lọ si kọ́lẹ́jì. Mo si tí siṣẹ́ ni ilé iṣẹ́ ìsúná ni àsikò nà, súgbọ́n ni bayìí ti mo pé ogójì ọdún, Ọlọrun sọ fún mi lati lọ dá ìjọ tèmi silẹ̀.

A si se ìfilọ́lẹ̀ ìjọ nà ni ìsàlẹ̀ ilé iṣẹ́ ibùdó rẹdio ti Kristiani, ni alẹ́ ọjọ́ àkọ́kọ́ ti a péjọ ni ibẹ̀, ó wa jẹ́ ìran tí Ọlọrun ti fi hàn mi ni bi ọdunmọ́ kànlélógún sẹ́yìn. Ninú ìsìn àkọ́kọ́ mo ri àwọn ìjọ ènìyàn ti mo ri ti wọn joko lorí àgà ti a le ká àti irú fèrèsé ti sokùnkùn tí mo rí nitorí ilẹ̀ ti sú. mo si rí pẹpẹ alábọ́dé bákannà.

Èmi àti Drenda fi ìjọ wa lọ́lẹ̀ inú wá si dùn nipa ìjọba ti a bá mọ kọbi ara sí nibiti à ngbé. Amọ̀ pe a o kó kúrò ninú ahéré ti a ngbé nitorí ti a ti tún pọ̀si ninú ẹbí wa nibayìí a ti ni àwọn ọmọ marùn ti o ti dágbà, kò si yàrá nilẹ̀ mọ́ fún wa. Bakannà, a nsiṣẹ́ oko-òwò wa ti o ti lọ́síwáju àti iṣẹ́ ìjọ ti inú wa ndùn nitorí rẹ̀.

Sùgbọ́n ni ọjọkan bi mo ti ilé ìjọsìn de, mo lọ si yàrá ìgbàlejò, mo joko sori ìjókóò. Bi mo ti jóko, lojiji, yàrá ti o wà layíka mi si pòórá, mo wá ri yàrá ti mo joko si pé kò sí àga kankan mọ níbẹ̀. Ẹnu lẹ̀kùn ti mo ba wọlé sí sílẹ̀ kọjú si ibìti a ti njẹun, àga ti mo joko le dojúkọ ilẹ̀kún ilé ounjẹ na, mo sì nwò inú yàrá nà lati ibi tì mo joko si, mo si ri pé àti palọ̀ àti ilé ìjẹun ni ó ti sófo kò si si nkan ninú wọn. Ìran yìí kò ju bi ìsẹ́jú àyáá márun lọ. Bi mo ti ríi, mo mọ̀ pé o tí tó àkókò lati kúrò ni ahére wa. Nigbati ìran nà ká lọ, Ni kíàkia ni mo ti sọ fún Drenda nkan ti o sẹlẹ̀ mo si sọ fún pé àsìkó ti lọ.

Lẹ́ẹ̀kansi, mo gbàgbọ́ pé Ọlọrun nlo ìran lati sọ ètò rẹ fún wa ki o baà le yé wa. Lóòtọ́ ni a nsiṣẹ́ tí ó le mú wa lati ma fènídọ́la. Sugbọ́n ìran sọ ni bí ó ti se kiakia tó “Àsìkò niyìí lati lọ!!!” Lẹ́yìn ọ̀ rẹyìn ní a to mọ́ idí ti o fi

jẹ́ kiakia. Ati yá aheré ti a ngbé yìí ó tí nlọ fún bi ọdún mẹ́san, a si ti mọ̀ pé a ni lati kúrò ngbàti àwọn à bá ni tún ilé se ba ti bẹ̀rẹ̀ etò ti wọn, sùgbọ̀n kò sí ẹnikan ti ó mọ̀ igbà ti yóò jẹ́.

Kí nge ìtàn nà kúrú, Ọlọrun darí wa sí ibi ilẹ̀ kan ti o dára ti àwa nà nkọ ile wa titún si. Èrò wa ni kí a rọ ram á siṣẹ́ ilé na lọ pẹ̀lẹ́pẹ̀lẹ́ ki a le ni ayè fun, boyá ki a lo bí ọdún kan tàbí mejì ki a fi kọ́ ọ. Súgbọ́n, nigbàti a o fi siṣẹ́ lórí ilé nà fún bi osù mẹfà, baba onile ti a ngbé kọ ìwe si wa lati fí ahéré wa silẹ̀ láàrin osù kan, a wá ba sọ́ wipé àwa nà nkọlé tiwa nà lọ́wọ́ ki o jọ́wọ́ fún wa ni bi osù mejì si mẹta sí i, ti ó sí gbà pé kò gbọdọ̀ ju bẹ́ẹ̀ nà lọ nitori kò si àyè ore-ọ̀fẹ́ mọ.

Ó dáa, à kó ohun gbogbo sinú ọkọ̀ lọ si ilé wa titun ni igbà ti àkókò ti wọn fún wa pé. Tí Ọlọrun kò ba tì sọ fún wa pé ki a kúrò ti a si se bẹ́ẹ̀, kò ba gbà wa ni akókò gàn , wàhálà ni kò ba tun jẹ́ fún wa.

Lóòtọ́, ìtàn ìkuuku bulu ti mo sọ fún yin ni ìbẹ̀rẹ̀ ìwe yìí, ti ọ jẹ́ ìsẹ̀lẹ̀ ti ó yí àyé mi padà, jẹ́ ìran ọrun pẹ̀lú. ìyàtọ̀ diẹ̀ ni o wà nibẹ́ ni ti ọgbọ́n ori pé mi o rí àwòrán ọjọ́ ọ̀la mi, sugbọ́n mo joko ninú ikuuku bulu yìí mo si ngbọ́ kedere àwọn Ọ̀rọ̀ ti Ẹ̀mi mimọ́ nsọ ti ò npé mi lọ si orílẹ̀-èdè ayé gbogbo.

Mo si mọ̀ dajú pé àwọn ìran ọ̀run miràn tún wà ti mo ti ní, sùgbọ́n ó dàbí pé àwọn àlá ni ó wọ́pọ̀ ti mo ma nlá. Nigbati mo nlọ sí Albania, o ku bi ọsẹ kan ti mo fẹ́ lọ, mo la àlá nipa ìrìn àjò ti o nbọ̀ tí mo fẹ́ lọ. Ni akókó yìí ninú ayé mi, mi o ti ma rin ìrin àjò rárá bi ìsinsinyìí; sáájú ki Ọlọrun tó ba mi sọ̀rọ̀ ni ọjọ́ nà, ki ise pé ó wù mi lati se bẹ́ẹ̀.

Sùgbọ́n, ó ku ọ̀sẹ̀ kan ti ma kúrò ni bẹ̀, mo lá àlá. Ninú àlá yi mo wà ni ofisì Dọkita ti mo dùbúlẹ̀ sórí tabili ti wọ́n nfi sèdánwò, nọ́ọ̀sì kan wa sinú yàrá ti mo wà o sì sọ fún mi pé ohun fẹ̀ mu lara ẹ̀jẹ̀ mi. Ó mu mi lọ́wọ́ dání o nyẹ ọmọ íka àrin ọwọ́ mi wò lati gba ẹ̀jẹ̀ na, ti mo rò pé ó sàjẹ̀jì. Sùgbọ́n, se bi o mọ̀ bi àlá ti má nri: àwọn nkankan wà ti wà fi mọ pé àlá ni.

Ninú àlá yìí, mo mọ̀ pékin tó kúrò lórí ilẹ̀ ayé yìí gbogbo ọmọ ìka ọwọ́ mi ni wọn yóò fi abẹ́ gún fún ẹ̀jẹ̀. Èyí si ba mi sọ̀rọ̀ torí ni ilé ẹ̀kọ́ Bibeli, wọn kọ́ mi pé à le lo ọwọ́ lati rán wa létí agbo márún ti ìjọ; àtanpàkò ọwọ́ dúró fún àpọsteli, ọmọ ìkati a ma n nà jẹ́ wolii,ìka ti àárín jẹ́ ẹ̀fanjẹlisti, ìka ti a nfi orùka sí jẹ́ Pasitọ̀, ti ọmọ ìka kékeré nse olukọ́ ti oun ati Pasítọ̀ jọ́ nsiṣẹ́ papọ̀.

Torínà, mo ni òye nkan ti nọ́ọ́sí nsọ fún mi. mo mọ́ pé ni ìgbésí ayé mi, màá, ó kéré tan ma siṣẹ́ ninú àwọn ọfisi ìjọ wọ̀nyìí. Pasitọ ni mi olùkọ́ sí ni mi pẹ̀lú, bẹ́ẹ̀ni,mo si tún mọ pé mo ni ọ̀rọ̀ àsọtẹ́lẹ̀ fún ìjọ ni ti ìjọba àti ìsúna. Ohun tí Jesu pè mi sí nìyí ngbati mo wa ni Albania. Àlá na fi nọ́ọ́sì tí ó nfi àbẹ́rẹ́ gún ọmọ ìka ọwọ́ mi ààrín, mo si mọ̀ pé a rán mi gẹ́gẹ́ bi ẹ̀fangẹ̀listi lọ sí gbogbo Albinià pẹ̀lú ìròyìn ayọ̀ ti ìhìnrere. Mo si sẹ̀ṣẹ̀ fẹ́ bẹ̀rẹ̀ nibayìí ati wọ́ inú iṣẹ̀ ìransẹ̀ àposteli ninú ayé mi.

Lẹ́yìnnà, ninú àlá ná lẹ́yìn ti nọ́ọ́sì ti se èyí tán, o wà mú ọwọ́ rẹ̀ mejeji papọ̀ bi ìgbà ti ọmọde bá ngbàdúrà, ó wa wo ojú mi ó sì sọ̀ jẹ́jẹ́ pe gbadura. Kò sọ̀rọ̀ nà sokè, o kan rọ ra sọ ni pé gbàdúrà bi ẹni ti o wà nibi ti kó ti gbọdọ̀ sọ̀rọ̀. Lati inú àlá ni mo ti mọ pé a rán mi bi ẹfanjẹ́listi lọ́ si orilẹ̀-èdè Albania, ati ki ngbàdúrà lorí ìrìn àjò nà.

Mo ti la ọ̀pọ̀lọpọ̀ àlá ti o pọ̀ ju ohun ti mo le máa kà lọ tàbi kin máa sọ nibiyí, sùgbọ́n àlá jẹ́ ohùn ti Ẹ̀mi Mimọ́. Bayìí, Mo ti bá àwọn ènìyàn padè ti wọ́n nla àla ni gbogbo alẹ́ ti o si dà bi ẹni pé ati ohungbogbo rí bíi “tẹ̀mi.” Mo gbàgbọ́ pé o ni lati dá awọn àlá ' mọ̀ yàtọ́, bẹ́ẹ̀ni, àwọn kan tún wà ti wọ́n fẹ́ ma ríran bi ẹlẹ̀mi lati le gba ara wọn layè ati ma se gàrù gbéraga ni ti ẹ̀mi, àti máa ri nkan ti kò tí ọ̀dọ̀ Ọlọrun wá. Sibẹ̀sibẹ̀, ki se ọ̀pọ̀ ìgbà ni mo fin la àlá. Ninú ọdun kan, mo le la àla ni ìgbà mẹ́rin si mejilá ti mo sí mọ̀ pé ọ̀dọ̀ Ọlọrun ni ó ti wá ti o si fi awọn nkan ti o lápẹẹrẹ hàn mi. Iye ìgbà ti mo fi nla àlá le pọ̀ si tabi dinkú ni arin ọdún, bẹ́ẹ̀ni. Èmi o lerò pé ohun ti ó lapẹẹrẹ nkankan wa ninú ìye ìgbà ti ọ fi lá àlá, bikose ẹ̀kọ́ ti o ri kọ́ ti o sì lapẹẹrẹ.

Àla ti o nyí ayé ẹni padà, ti o yí ayé mi padà ni ìgbà ti Ọlọrun sọ fún mi pé kin fi ilé ìsẹ́ ìsuna mi ti mo ti nsiṣẹ́ lati bi ọdun mẹjọ silẹ̀ kin si lọ bẹ̀rẹ̀ ilé ṣẹ́ ti ma ti ma ran àwọn ènìyàn lọwọ́ ati bọ́ ninú gbèsè. Èléyìí jẹ́ nkan tí ó ni àpẹẹrẹ to dajú.

Bẹ́ẹ̀ nà ni àwọn àlà ìkilọ̀. Mo le ránti ọkan tí ó jẹ́ àjèjì si mi àlá ìkilọ̀. o selẹ̀ ni àsikò ti ìsuná ile iṣẹ́ ìránsẹ́ fẹ̀ maà lọ̀lẹ̀, isoro àti nàwò diẹ̀ wà. Ninú àlá yìí, mo fẹ̀yìn lélẹ́ lorí ibùsùn orun ti fẹ́ má a rá mi lọ. Ìlẹ̀kùn yàra na si silẹ̀, mo si ngbọ́ ariwo diẹdíẹ̀ ninú gbọ̀ngàn (lojú àlá mi) mo wòó fírí lati ẹnu lẹ̀kùn. Nigbànà ni mọ ri èsù kekeré kan , tií kò ga ju ìwọ́n bàtà mẹ́ta àti àbọ̀ lọ,ti nfa asọ kan ti ó di owò si lẹ́yìn rẹ̀. Apò owò na dabi ti Santa Claus yóò lò. Èsù ni o nfa àpo yí, apò na si wúwo torí ó kún fún owó, ni o

se nwọ́ àpò na nílẹ̀. ki ise pé o fẹ́ jade ninú ilé, sugbọ́n mo gbọ́ tí ó yí po ti o ngba ọ̀nà si àja kẹta ilé lọ. Bi mo ti tají mo nrònú nipa àlá nàa, mo wa rí pé Oluwa nfi hàn mi pé owó nsọnù tàbi pé wọ́n njí owó lọ́nà kan.

Ohun ìyàlẹnu ni pé mo mọ iye owó ti o wà ninú àpò na ni ojú àlá mi. Mo si ránti pé mo nrò pé owó tí ó tó ẹgbẹ̀rúnmẹ́ẹ̀dọ́gbọ̀n dọlla ni. Mo tún wòó pé niwọ̀n ìgbà ti èsu na kó jáde kurò ninú ile, tí o sì gbé owó na lọ sí òkè ni a jẹ́ wipé ẹni nà tàbi awọn ti o njí owó tàbi lo owó na ni ilòkulò jẹ́ ara àwa ti ó ngbe inú ilé; àti ara wà, mo si mọ́ pé ninú iṣẹ́ ìrànṣẹ́ wa ni. Ohun ti mo se ni ọjọ́ kejì ni pé mo pe alàgbà kan ninú wa pé ki ó lọ́ se àyẹ̀wò àwọn ìwe owó ni ẹka wọ́n. Nipa sise èyí a ri àwọn ìnawó kan tí kò nilò ti a fojúfò. Nigbà ti a sí gbogbo àwọn owó nina yìí papọ̀ o jẹ́ ẹgbẹ̀rúnmẹ́ẹ̀dọ́gbọ̀n dọlla ni osù kan. A si pinnu pé kò sí ẹnikan ti o njalè, sugbọ́n nipa àìlákàsí, à nlo owó na nilòkulò tàbi awọn Kankan wa ti o yẹ ki a mu kúrò ninú inawó wa. A nilò iru owó bayí ni àsikò ti nkan le koko.

Ọlọrun le lo àlá lati fi àwọn ètè/ìlànà han ọ ba kanna. Ni ọdun ti ó kọja lọ 2018, Mo lá àla kan ti o jẹ̀ ohun gbogbo ti mo ngbọ́ ni ọ̀rọ̀ "Pè ọkọ́ ojú omi nà lẹ́jọ́" mo kọ́sílẹ̀ sugbọ́n mi o le sọ ohun ti ó jẹ́. Mo sì nbi Oluwa nipa rẹ̀" mi o si sọ fún ẹnikẹ́ni yàtọ̀ si Drenda nipa rẹ̀. Nigbati à nse ìpade àwn ọkùnrin ninnú osù kinni, mo nsọ nipa àwọn nkan tí a o se ninú ọdún ti a bọ́ sí. Ọ̀kan ninú rẹ̀ ni àwọn èrò wa ti a ti ni fún bi ọdún diẹ sẹ́yìn lati ni àwọn ẹgbẹ́ kan ti yóò jẹ́ fún gbogbo orilẹ́-èdè tí ó wá sọ́kàn mi pé ninú ọdun yìí ni a o seé lẹ́yìn ti a parí ìpàdé, ọkàn lara àwọn ti a jọ sepàdé wá bá mi o sọ fún mi pé nkan ti oun fẹ́ sọ le dàbi ọ̀rọ̀ asiwèrè, ó sọ pé, Oluwa sọ pé ò dàbi Helen Troy". Nkan ti o nsọ gan kò yé mi, o wa bẹ̀rẹ̀ si ni se àláyé oun ti ó nsọ túmọ̀ si. Mo wa sọ fún pé ki o kọ́ ọ́ ohun ti o nsọ̀ ránṣẹ́ si mi lorí ímeelì. Nkan ti o kọ niyìí.

**ỌLỌRUN LE LO ÀLÁ LATI FÚN Ọ NÍ ÈTE TÀBÍ ÌLÀNÀ BÁKANNÀ.**

*Spart ọba, Menelaus ti pàsẹ fún ẹgbẹ̀rúnkan ọkọ̀ ojú omi láti lọ gba ìyàwó rẹ̀ sílẹ̀, Hellen lọ́wọ́ àwon Trojans. "Ibiti àwọn ẹgbẹ̀rúnkan ọkọ̀ ojú omi ti jáde wá nà ni à npè ní Hellen ti Troy.*

*Ní o.jọ́rú tí ńse ọgbọ̀njọ́ osù ìkínní ọdún 2019, nígbàtí Pásítò ńsọrọ̀ nínú ìpàdé àwọn ọkùnrin, Oluwa sọ wípé ó sì dà bí Helen ti Troy, ọba sì fi ẹgbẹ̀rúnkan ọkọ̀ ojú omi láti lọ gba àwọn tó ti sọnù, sọnù nínu ìgbàgbọ́, sọnù nínú ẹbí àti sọnú ìsúná wọn.*

*Emi ni*
*Aaroni*

Ó tún fi Imeeli míràn sọwọ́ sí mi lọ́jọ́nà.

*Pásítò,*

*Mo fẹ́ láti sọ̀rọ̀ àti wo Helen Troy bí ológun. Sí ọ̀pọ̀ èniyàn, wọ́n ri i bi ìtàn ọba kan tí o lo ẹgbẹ̀rún kan ọkọ̀ ojú omi síta láti lọ gba ìyàwó rẹ̀ tó sọnù lọ́wọ́ àwọn ará Trojans. Sùgbọ́n bí ẹni tí ronú bí ọmo ológun, isẹ́ tí a yàn fun ọmọ ogun ni láti se ti a pè ní isẹ́ Helen ti Troy. Gbogbo isẹ́ tí wọ́n bá yàn fún àwọn ọmọ ológun ni wọn ńsọ ni orúkọ. Fún àpẹẹrẹ isẹ́ tí àwọn ẹgbẹ́ SEAL Mẹ́fà tí wọn lọ se ìkọlù sí ọgbà ilé Osama Bin Laden ni wọn pè ní Neptune Spear. Wọ́n ti rán èmi na lọ sisẹ́ kan pẹ̀lú orúkọ tí ó rẹwà bí isẹ́ Forward Mike, Elvis Marshall ati Santa Claus.*

*Àwọn orúkọ ìnagijẹ lẹ́nu isẹ́ wà tí wọ́n ma pe ara wọn láti fi le dá ara wọn mọ̀, láti jẹ́ kí wọ́n mọ irú isẹ́ tí wọ́n fẹ́ lọ lati se, àti mọ ẹnití ó ńgba isẹ́ nà tàbí ẹnití yóò se isẹ́ nà. Nígbàtí Olúwa sọ wípé o dà bí Helen ara Troy, ọkàn ti Ológun ti mo ní ni ó jẹ́ ki túmọ̀ rẹ̀ sí Pasitọ Garry ni ó rán ọmọ ogun lọ si Helen Troy, isẹ́ lamti lo ẹgbẹ̀rúnkan ọkọ̀ ojú omi lati lọ gba àwọn to sọnù nínú ìgbàgbọ́,* sọnù nínú ẹbí àti sọnú ìsúná wọn.

*Síwájúsi, nígbàtí mo gbọ́ nmipa isẹ́ ti ẹlẹ́gbẹ̀rúnkan ọkọ̀ ojú omi, Mo tún ronú nípa iye àwọn jagunjagun, àwọn òsìsẹ́ tí yóò kún wọn lọ́wọ́, ìdánilẹkọ, àwọn ohun tim yóò ná wọn, àti ètò ìsàkóso tí o máa nam wọn ki wọn to le rán àwọn ọkọ̀ ojú omi kọ̀kan jáde.*

*Kò sí ẹnìkan tí ó le pàsè isẹ́ yi fún àwọn ọmọ ogun ti ìjọba Ọlọrun ju ìwo náà lọ. O ti lo ọ̀pọ̀ odún láti fi kọ́ wa fún irú àkókò yìí. Àwọn ẹbí mi, mo sì mọ̀ dájú pé àwọn ara tókù na láyọ̀ lati lọ sisẹ́*

*Nínú isẹ́ Rẹ̀*

*Áárónì*

Aàroni jẹ́ ọmọ iṣẹ́ ogun alábò oju omi ti o ti lọ sisẹ́ ni bi ọ̀nà mẹ́san nigbati ó wà lẹnu ìsẹ́ fún bi ọdún mọ́kànlélógún ninú iṣẹ́ ọlọgun. Ìtàn ayipada ti o ba ayè rẹ nipa agbára ti agbelébu jẹ́ ohun nla. Kò mọ ohun ti Ọlọrun ti sọ fún mi ninú àlá, lati gba àkóso ọkọ̀ oju omi, Sùgbọ́n "ọ́rọ́ ìmọ̀" rẹ fi àrídáju fún mi pé mo gbọ́ ọ dáadáa ati rànmi lọ́wọ́ lati mu ọ̀nà mi pọ̀n bi Ọlọrun ti fẹ́ ẹ fún mi. Afojúsùn wa ni lat pèsè àwọn ọmọ ẹgbẹ́ bi ẹgbẹ́rúnkan ti yóò ma pín ìròyìn àyọ́ ti ìjọba Ọlọrun kàákiri gbogbo orilẹ́ èdè. Ti o ba fẹ́ jẹ́ ọkan lara àwọn ọmọ ogun wọ̀nyìí, jọ̀wọ́ kàn si mi nipaṣẹ̀ ìtàkùn ayélujara yìí, Graykeesee.com.

Mo lerò pé ó yé ọ pé. Àlá jẹ́ ọnà ti ó lágbára ti Ọlọrun lò lati bá àwọn èniyàn rẹ̀ sọ̀rọ̀, ranwọn lọ́wọ́ pẹlú ìtọsọna, ètè, ìkìlọ̀ àti ìtùnnú.

Kí a tó parí ẹkọ́ yìí, ma tún fẹ́ fi ọkan ninú àwọn ọ̀nà ti Ọlọrun ma nlò lati ràn ètè ìlànà wa lọ́wọ́, ti ise ẹ̀bùn àsọtẹ́lẹ̀. Aàroni ti gba ẹ̀bìn ìmọ̀ ọ̀rọ̀ nipa àwọn ètó titun ti a ni. Imọ ọ̀rọ̀ ni ohun ti o sọ, Ọ̀rọ̀ ìmọ̀. Èyí ni ìmọ̀ ti Ẹ̀mi Ọlọrun sọ fún ọ, nkan ti o kò le mọ̀ fúnra rẹ. Awọn ọ̀rọ̀ ìmọ ni a kọsílẹ̀ ninú ìwe 1Kọrinti 12 bi awọn ẹ̀bùn mẹsán ti Ẹ̀mi Mimọ́. Bayìí, mi ò fẹ́ lati sọ̀rọ̀ púpọ̀ ninú ìwe yìí nipa ẹ̀bùn ti ẹ̀mi, sùgbọ́n ma kan sọ̀ nipa ọkan ninú wọn ti nse àsọtẹ́lẹ̀.

> **"SÙGBỌ́N ẸNITI NSỌTẸ́LẸ̀ MBÁ ÀWỌN ÈNÌYÀN SỌ̀RỌ̀ FÚN ÌMÚDÚRÓ, ÀTI ÌGBIYÀNJÚ ÀTI ÌTÙNÚ."**
> **— 1KORINTI 14:3**

Ọ̀pọ̀ ni o ti sọ ayé wọn di ìdàkudà nipaṣẹ́ aìlóyé àwọn ẹ̀bun wọ̀nyìí ti a dàrúkọ. Nigbàti àwọn ènìyàn ba nronú nipa àsọtẹ́lẹ̀, wọn ma nròó pé wolii ni o yẹ ki o pe àwọn ki o má sọ àsọtẹ́lẹ̀ fún wọn, pe ó yẹ ki o lọ si Afrikà tàbi Pasitọ ni o yẹ̀ ki o jẹ́." Àwọn gbólóhùn mejeji yìí le jẹ́ àsọtẹ́lẹ̀, bẹ́ẹ̀ni mejeji na le jẹ́ àsise bakannà, sùgbọ́n bi wọn

bá kàá bi wọ́n ti sọ, wọn le jẹ́ otọ́. Paulu ti sàláye èredi àsọtẹ́lẹ̀.

*"Sùgbọ́n ẹnití nsọtẹ́lẹ̀ ḿbá àwọn ènìyàn sọ̀rọ̀ fún ìmúdúró àti ìgbìyànjum, àti ìtùnnú"* (1Kọ́ríntì !4:13).

Níbẹ̀ ni a ti ríi. Kòsí ọ̀rọ̀ kan ti o fi hàn pé o ni lati wá ìtọ́ni nipaṣẹ àsọtẹ́lẹ̀, sibẹ̀ bi ọ̀pọ̀ àwọn ènìyàn ti nrí àsọtẹ́lẹ̀ niyìí pẹ̀ ó nfún ni ni ìtọsọnà. Sùgbọ́n bi Paulu ti sọ àsọtẹ́lẹ̀ wà lati fi idi ìtọní múlẹ̀, ki íse lati fún ni itọni. Se o ri nikété ti o ti di àtunbi, Ẹ̀mi Mimọ́ ninú rẹ NÍ yóò ma sọ àwọn ohun ti wàá se fún ọ. O kò nilò okùnrin tàbi obinrin kan lati máa sọ ohun ti a pé ọ lati se fún Jesu, Bikòse ọ̀rọ̀ àsọtẹ́lẹ̀ ti yóò fi ìdí nkan ti o ti mọ̀ tẹ́lẹ̀ múlẹ̀.

Fún àpẹẹrẹ, ninú àwọn àkàwé bti mo ti sọ fún yín,"Ó yẹ kí o lọ sí Áfrikà" mo sọ pé èyí le jẹ́ àpẹẹrẹ ọ̀rọ̀ àsọtẹ́lẹ̀ tòótọ́, tí Ẹ̀mi Mimọ́ ba ti sọ fún ọ tẹ́lẹ̀ ti Ó wá nfi idí rẹ̀ múlẹ̀ nipaṣẹ ọ̀rọ̀ nà. Sugbọ́n ti lilọ si Áfrikà kò ba si ni ọkàn rẹ tí ó si jẹ́ ìgbà àkọ́kọ́ niyìí ti o sẹ̀sẹ̀ gbọ, à jẹ́ wipé kò le jẹ́ àpẹẹrẹ tòótọ́ ti ọ̀rọ̀ àsọtẹ́lẹ̀ ninú ìjọ Majẹ̀mú Tuntun.

O jẹ́ ọ̀rọ̀ ti kò bójúmu ki awọn ènìyàn ma sọ wipé, mo ri Kristiani kan ti o wa sọ fún mi pé "Ọlọrun sọ fún mi ninú ìpàde pe ó yẹ́ kín ti se rere." Ò dáa, bẹ́ẹ̀ni, o kò nilò ẹnikẹ́ni lati wá sọ ọ̀rọ̀ fún ọ pe wàá serere; Bibeli ti sọ fún wa bẹ́. Mo ti rí Kristiani ti o nlọ kiri ti ó nbere lọ́wọ́ àwọn ènìyàn pé bóya wọn ni ọ̀rọ̀ fún wọn. O kò nilò ẹnikẹ́ni lati sọ̀rọ̀ fún ọ; Ẹ̀mi Mimọ́ ninú rẹ yóò ba ọ sọ̀rọ̀ ati pé, bẹ́ẹ̀ni, Ọlọrun le fi ọ̀rọ̀ àsọtẹ́lẹ̀ kan ransẹ́ si ọ lati mu dá ọ lójú àti gbà ọ niyanjú, sùgbọ́n ki ise lati dari rẹ́.

Nkan tí ó sẹlẹ́ ninú ayé mi bi àpẹẹrẹ nigbati Drenda wà ni afẹ́sọna mi bi àpẹẹrẹ. Mo nlọ lati lọ rí àwọn ebi rẹ̀ ni Georgia lati bèrè pé mo fẹ́ lati fi se ìyàwò mi. Nigbàti mo wà nibẹ̀, ó yẹ kí àwa mejeji jọ lọ si ìjọ wọn. Ni àsikò yìí gàn ni mo sẹ̀sẹ̀ gba iṣẹ́ ni ilé isẹ́ ètò ìsúna kàn ti mo si njijakadì pẹ́lu rẹ̀ lọ́wọ́. Ati pé mi lati wá wàásù nigbàti mo wà ni ọmọ ọdún mọkàndinlógun mo si sẹ̀sẹ̀ parí kọlẹ́jì ni pẹlú digiri ninú Majẹ̀mú Laílaí, sibẹ̀ mo lerò pé o wù mi lati gbá ise ètò ìsúna yìí. Nigbana ó sì rúmilojú nkan ti mo le se.

Lẹ́yìn ti a se ìsìn tan ni ọjọ ìsinmi ni ile ìjọsìn àwọn Drenda, Arabinrinkan ti mi ò mọ, sìgbọ́n ti Drenda mọ dáadáa, Tọ mi wá o si wipé

ohun ni ọ̀rọ̀ kan tí ohun fẹ́ sọ fún mi. Ó ni, “Ò n wa iṣẹ́. Iṣá na si ní àwọn nkan mẹ́wa yìí ninú, bi o sì ti dárúkọ́ gbogbo àwọn nkan ti ma má se ni ibi iṣẹ́ titun mi yìí” Ó ni, ó yẹ ki o gba iṣẹ́ yìí nitorí Ọlọrun wà ninú rẹ̀" Ni torí èyf, mo ti fẹ́ lati gba iṣẹ́ nà sùgbọ́n o rú u lojú idi ti o fi rí bẹ́. Ọ̀rọ̀ àsọtẹ́lẹ̀ rẹ̀ mú ìtùnnú àti ìgboyà wa fún mi o si fidí ìtọnísọna ibiti ma lọ. Lẹ́ẹ̀kansi, Ẹ̀mi Mimọ́ inú rẹ ni yóò tọ́ ọ ati jẹ́ olùtúní rẹ.

ORÍ KỌKÀNLÁ

# ÈMI MIMỌ́ NDÚN BÍ ÒGÁ MI.

Mo ni ẹbí ninú ìjọ mi, nigbà ti ó si wà ní agbo kékeré, ti wọn nilò isẹ́. Wọ́n jẹ́ ẹbí ti o ni ifẹ́ ti wọ́n si fẹ́ràn lati máa ran àwọ́n ti o wà ni àyíká lọ́ wọ́ pàápá ninú ìjọ. Súgbọ́n gbogbo ìgbà ni owó ma njẹ́ isòro fún wọn. Ó dá, iṣẹ́ tùn ti bọ lọwọ́ baba wọ́n, torinà mo pinnnu lati ràn wọ́n lọwọ́. Ni àkókò yìí, ni mò nkọ́ ilé mi lọ́wọ́ ti mo sì nsisẹ́ fífa iná si lọwọ́ fún ara mi. mo wa ri pé baba wọn nà mọ̀ nipa iṣẹ́ ina fifà si ilé díẹ, mo si sọ fún pé ma fún ni owó iṣẹ fún idajì wákàti tí ó bá lò nitorí ounjẹ ti ntán lọ ni ilé wọn. Ó si wá latí se ìẹ́ẹ́ ti o bojúmu pẹ̀lú àwọn wàyá ìfana tí mo fún un.

Mi ó ti lẹ̀ ròó púpọ̀, sugbọ́n ni bi osú kan lẹ́yìn ìgbànà.Mo gba ìpè kan lati ọ̀dọ̀ ọmọkùnrin kan. Ó ni àwọn ènìyàn kan ti nkó ara wọn jọ lati gbàdúra fún mi. Mo sọ pé "Torí kínni" Pé nkankan wà ninú ìjọ ti ó ni lati yípadà, ó si tẹ̀síwájú lati sọ fún mi pé òun ti kọ nkan mẹwà sí lẹ̀ ti o yẹ ki wọn jiróró lé lórí. Àkọ́kọ́ ni ti ó kọsilẹ̀ ni ilé nla tí ó tóbi. Ó bi mi pé èló ni owọ́ ti àwọn ìjọ nsan fún mi ti o le tó gbà irú ilé nà. Mo tètè dalóhun pé ìjọ ko fún mi ni owò kankan, pé mi o gba owó ìwe sòwédowòn Kankan lọwọ́ ìjọ. Lẹ́yìn ti mo sọ nkan yìí, ó dakẹ́ díẹ̀. Nígbànà ni ó sọ wipé, "Ìjọ kò san owó fún ọ" Mo dalóhún. Lẹ̀ẹ̀kansi, ó dàkẹ̀ títí o fi wá sọ pé: "ó da, ó yẹ ki wọn ma sée" Bi a sé parí ọ̀rọ̀ wa niyìí.

Ó dáà, ó wa tó bi ọ̀sẹ̀ kan tàbi lẹ́yìn ìgbànà ni mó gbọ nipa ilé iṣẹ́ ti wọn si ti mo si lérò pé o le sisẹ́ nibẹ̀, mo si sọ fún un nipa rẹ̀. Ó si lọ lati lọ fi ìwe ìgbàṣẹ́ silẹ̀ nibẹ̀ ó si rí iṣẹ́ na gbà. Ranti pé wọ́n ti fẹ́ le àwọn ẹbí yìí kúrò ni ilé ti wọn ngbé ni akókò kan. Ni ọsẹ̀ ti ó gba íṣẹ́ nà ó wà sí ilé ìjọsìn ó si sọ fún mi pé óun ti kúrò, ó jọmilójú. Ó kúrò; Kilódé?" Ó sọ fún mi pé ni ọ̀sàn ọjọ́ Jimọ̀ ti awọn ti parí iṣẹ́ ọ̀sẹ̀ nà tán ti wọ́n ni ki o lọ gbálẹ̀. Ò ni

nigbànà ni oun kúrò, pé óun kò fọwọ́si lati wa gbálẹ̀. Mi o lé gbà ohun ti mò gbọ́ gbọ́. Mo mọ́ pé àrakunrin yìí nilò ìdanilẹ́kọ́ tí ó lágbára Ti o bá fẹ́ ni àseyọrí ninú ayé. Gbogbo ìgba ni àànu ìyàwó ọkùnrín yìí ma nse mi. Kó pẹ́ ti wọ́n fi kúrò ni ile ìjọsìn wà lẹ́yín ìgbànà, mi o sì mọ ohun ti n sẹlẹ̀ sí wọn mọ. Sibẹ̀sibẹ̀, ó si le se iṣẹ́ ti o dára bi mo ti lerò. Lorì ìwà ìgberaga àti àifẹ́ isẹ́ se rẹ̀. Mo rò pé bibẹ̀rẹ̀ padà rẹ ti mu ki o ti jẹ́ ki o kurò ninú àwọn iṣẹ́ diẹ̀ to ti se ọ̀pọ̀ fún ìgbà diẹ. Lati le se rere rẹ̀ yóò jẹ̀ ọ̀na àti farada ni ayé. Nibáyìí, ma sìmìgbọ́. Awọn ènìyàn ma nyí padà, mo si nretí ki òun nà yípadà nirorí ara rẹ̀. Sùgbọ́n ohun tí mo mọ̀, nigbàti mo ti mọ̀ ọ,ó nlọ si oko ìparun. Se o rí, kò ka ohùn Ọlọrun sí.

O le bérè pé, “kinni ohùn Ọlọrun ni se ninú nkan ti a nsọ̀rọ̀ nipa rẹ̀? Mo mọ̀ dajú pé ohun ti yóò sọ niyìí ti ó bà bèrè lọ́wọ́ rẹ̀, nitorí ni àkókò yìí kò ti mọ ohun ti yó se. Sùgbọn ó ti fojúfo ohun ti nsọ̀nà kan ninú idanilẹ́kọ́ àti pípèsè àwọn ènìyàn ti àwọn silẹ̀ fún àyànmọ́ wọn: kíkọ́ ìtẹríba. Mo mọ̀ àkọlé ìpín yìí le máa rú yín lójú. Kínni ọ̀gá mi ni se pẹ̀lú Ẹ̀mi Mimọ́? Wà mọ̀ di ninú ìpín yìí pé ọ̀gá rẹ ni ọ̀pọ̀ ohun lati se pẹ̀lú agbára rẹ lati ma gbọ́ ohùn Ẹ̀mi Mimọ́!

Mo fẹ́ bẹ̀rẹ̀ ẹ̀kọ́ lorí àkòrí wa ti o se pàtàkì yìí Mattiu 8:5-10.

> *Nígbàti Jesu sì wọ Kapérnaumù, Balógun ọrun kan tọ̀ọ́ wá, ó mbẹ̀ ẹ́, “Ó sì wípé Olúwa, ọmọ ọ̀dọ̀ mi dùbúlẹ̀ àrùn ẹ̀gbà nim ilé, ni ìrora púpọ̀.”*
>
> *Jesu wí fún pé, “Èmí nbọ̀ wa mú u láradá.”*
>
> *Balogun ọrun naa dáhùn, o sì wipé, “Olúwa, èmí kò yẹ tí ìwọ ìbá fi wọ abẹ́ òrùlé mi: sùgbọ́n sọ kìkì ọ̀rọ̀ kan a o si mú ọmọ-ọ̀dọ̀ mi láradá. Eniti ó wà lábẹ àṣẹ sá ni èmi, èmi si ni ọmọ ogun lẹ́hìn mi: mo wi fún ẹnìkan pé, Lọ, a si lọ; àti fún ẹnikejì pé, wá, a sì wá: àti fún ọmọ-ọ̀dọ̀ mi pé Se èyí a sì seé.”*
>
> *Nígbàti Jesu gbọ, ẹnu yàá, ó sì wí fún àwọn tí ó mọ̀ ọ pé, lótọ ni mo wí fún yín, “èmi kò rí ìgbàgbọ́ ńlá bí irú èyí nínú àwọn ènìyàn Ísráẹ̀lì ní ti ó se.”*
>
> —Máttíù 8:5-10

Kílóde ti arakunrin yìí se gbàgbọ́ bẹ̀ pé Jesu le wo ọmọ-ọ̀dọ̀ rẹ̀ sàn? Fúnrarẹ̀ ni o dahùn ibéèrè nà. *Ẹniti ó wà lábẹ àsẹ sá ni èmi, èmi si ni ọmọ ogun lẹ́hìn mi: mo wi fún ẹnìkan pé, Lọ, a si lọ; àti fún ẹnikejì pé, wá, a sì wá: àti fún ọmọ-ọ̀dọ̀ mi pé Se èyí a sì seé"* Nitorí ó mọ̀ bi àṣẹ ti se nsiṣẹ́. Bi óun nà ti se wà labẹ́ àṣẹ, àwọn ọmọ rẹ̀ nà wà labẹ́ àṣẹ rẹ̀. Ọ ní ìwoye pé ọ̀rọ̀ tí ọ̀gá rẹ̀ ba sọ ndún bi ohùn ti Kaesari. Kódà, ti o ba mọ òtítọ́, ohùn ọ̀ga rẹ̀ ni ohùn Kaesari. Ó si tún mọ̀ pé, ohùn rẹ̀ si ọmọ-ọ̀dọ̀ rẹ̀ ndún bi ohùn Kaesari létí wọn. Ti o túmọ̀ si latí wà labẹ́ àṣẹ, ó gbọ́ awọn ọ̀rọ̀ nà yé bi Jesu ti se lo àṣẹ lórí isòro nà nipa biba sọ̀rọ̀. Ohun gbogbo tí o yẹ ki òun nà se bákannà nìyìí. Tí ó bá sọ fún ọmọ ọ̀dọ̀ rẹ̀ latí se ohunkan, wọn yóò sé e. Bi ó ti rọrùn tó nìyìí. Òtítọ́ ti o gbọdọ̀ kọ́ nìyìí:

**O LE RÌN PẸ̀LÚ ÀSẸ BÍ O TI NTẸRÍBA FÚN ÀSẸ NÌKAN!**

Ti Satani bá le se lati mú gbogbo ìbọ̀wọ̀ fún àṣẹ kurò àti yí gbogbo ènìyàn lọkàn padà pé wọn le se ohunkóhun ti wọ̀n ba fẹ́ nigbàti o bá wù wọn, nigbànà ni gbogbo ayè yóò dojúdé sinu rúdurùdu àti parun. Nkan ti o nfà pẹ̀lú Efa nìyìì ninú Ọgbà, " Se lòótọ́ ni Ọlọrun sọ ọ́. . .?" Gbọ́ gbogbo ẹnikẹ́ni ti ó wà lórí ilẹ̀ ayé yí ni ó wà labẹ̀ òfin tàbi làbẹ̀ onirúruurú àwọn àṣẹ. Dá abẹ́ àṣẹ ẹniti ọ wà mọ̀ yóò ràn ọ lọ́wọ́ lati le mọ ẹniti ó yẹ kí ó máa tẹ́tí sí àti ẹniti kò yẹ́ ki o gbọ̀ tirẹ̀. Sùgbọ́n lóde òní, gbogbo ènìyàn ni ó fẹ̀ lo àṣẹ laísí lábẹ́ àṣẹ, kó sì le sé e se.

Laipẹ́ yìí, mo nbá agbanisiṣẹ́ kan sọ̀rọ̀ ti ó nsọ fún mi bi o ti máa nsan owó fún àwọn ènìyàn nitorí ki ó ma bá sàn owo orí osisẹ àti owó òya gbà má bínnú osìsẹ́. Sugbọn èmi ti mọ ibiti ohun ti ó nse yóò yọ rí sí. Ni ọjọ́ kan, ọkan ninú àwọn osìsẹ̀ yóò farapa wọn ó si bèrè fún owó ò ya gbà mabinnú àwọn ọsisẹ́ wọn ó wa ri nkan ti ọ̀gà wọn nse pé kó kí san owó yi si ibiti o yẹ kí o san án sí ibi ilé isẹ́ gbà mà binnú àwọn osísẹ́, yóò si pèe agbánisíṣẹ́ na lẹ́jọ́ nitorí ó wà làbẹ́ òfin pé kí o má sàn owó nà. Mo ti gbọ́ irú ìtàn yí rí ti ó sẹlẹ̀ ninú ìjọ wà pẹ̀lú àwọn agbanisíṣẹ́ meji kan.

Ni ọ̀sẹ̀ ti ó kọjá, mo ba àrabinrin kan ti o ní òun kó nilò pasitọ̀ sọ̀rọ̀; òun ati Ẹ̀mi Mimọ́ nikan ni. Lóòtọ́? Ó dáa, Kò ba dára ki o lọ àti ba Jesu sọ̀rọ̀ nipa rẹ̀ nitorí Òn ni ẹniti ó nyan Pasítọ̀ àti gbé ìjọ agbègbè kalẹ̀ ninú Efesu orí Kẹrin. Ti ó ba tẹríba fún Jesu nigbànà yóò ma tẹ̀le àṣẹ ti Jesu gbé kalẹ̀. Ohun ti ó wà ninú rẹ̀ ni pe kò ni ìtẹríba fún Jesu ó si fẹ̀ ma se nkan ti o fẹ̀. O si se é se ki ó subú sinú ìtànjẹ̀ àti ìgbà ti ó le nitori rẹ̀.

Kò ti pẹ́ púpọ̀, ti mò nba ẹnikan ti ntajà sọ̀rọ̀ ti ó sẹ̀sẹ̀ bẹ̀rẹ̀ ile iṣẹ́ ara wọn ti wọn si nkó àwọn onibara wọn ti ilé iṣẹ́ ti wọn wà tẹ́lẹ́ lọ si ilé isẹ́ wọn, bi o tì lẹ̀ se pé wọn ti fọwọ́si ìwe pé àwọn kò ni se bẹ̀. Wọn sì lerò pé àwọn má ni àseyọrí ninú irú nkan yìí? Olè ni a npèé!

Mo mọ̀ pé o le ma nifẹ́ si ìpín yìí bi àwọn to kú ti mo ti sọ àwọn ọhun tí ó rekọjá òye, àwọn nkan ti kò le rárá tí Ẹ̀mi Mimọ́ nse, sùgbọ́n ti ìpín ẹ̀kọ́ yìí kó ba yé ọ dáadáa, a jẹ́ wipé ó le gbàgbé gbogbo àwọn ori tókù nà nitori Ọlọrun ni o má gbeniga.

Mo ranti ìgbà tí obinrin kan wá sọdọ mi ninú ìpade àdúrà tóun tomi lójú, ti ó bèrè lọ́wọ́ mi idì ti mi o se pè e ki ó gbàdúrà. Ẹ̀ru bà mi! Kin ni nkan tí ó wà nibẹ̀ pé mi o pè ọ lati gbàdúrà, torí kin ni, bẹ́ẹ̀ni,se ti rẹ̀ ni kí gbogbo ènìyàn tí dá mọ̀?

**DÁ ABẸ́ ÀṢẸ ẸNITI O WÀ MỌ̀ YÓÒ RÀN Ọ́ LỌ́WỌ́ LATI LE MỌ ẸNITI Ó YẸ KÍ O MÁA TẸ̀TÍ SÍ ÀTI ẸNITI KÒ YẸ KÍ Ò MÀA GBỌ́ TI RẸ̀.**

Àti pé lóòtọ́ ni mi ò bá ti sọ fún un ìdí ti mi o fi pèé ní ìsẹ́jú kan ti o bá ti ẹ̀ ma farabalẹ̀ gbọ́ ti ẹnikẹ́ni. Arabinrin yíì ki bọ̀wọ̀ fún ọkọ rẹ̀ àti pé gbogbo ìgbà ni o máa fi aìka nkan t'ẹ̀mi kún rẹ̀ si ìjòko àwọn olófófó. Ìdi nìyìí tí mi ò se pè. Sugbọn nitori ti ó sunkun wá nitori pé a kò ri bi ẹni ẹ̀mi, ó rò pé òun ti wà lojú ìjọ lati fi hàn pé kò bọ̀wọ̀ fún àṣẹ, irú àwọn àràbinrín tó léwu ni.

Jẹ́ kin wá berè lọ́wọ́ rẹ, se ó kòjú òsúnwọ̀n lati lọ́ sí ibi ti o fẹ́ lá ti lọ, ibití àlá rẹ fẹ́ lọ? Tí mo ba bèrè lọ́wọ́ Pasitọ̀ rẹ tàbi ọ̀gá rẹ. Kin ni èrò wọn yóò jẹ́, kin ni ohun tí wọn ò sọ? Se o rí i, o kò le ni àṣẹ à àyàfí ti o bá yege ninú ọ̀rọ̀ ìtẹríba. Èmi kọ́ ni o sọ bẹ́ẹ̀; Jesu ni.

> *Ẹnití ó bá se olóòtọ́ ní ohun kíkíní, ó se olóòtọ́ ní pípọ̀ pẹ̀lú: ẹnití ó ba sì se alamisòtọ́ ní ohun kínkíní, ó se alaimásòtọ́ ni ohun pípọ̀ pẹ̀lú. Ǹjẹ́ bí ẹ̀yin kò bá ti jẹ́ olóòtọ́ ni mámmọ́nì aìsòtọ́, tani yóò fi ọrọ̀ tòótọ́ su yín? Bi ẹ̀yin bá sì ti jẹ́ olóòtọ́ ni ohun ti ise ti ẹlómíràn, tani yóò fun yín ní ohun tí se ti ẹ̀yin tìkara yín?*
>
> —Luku 16:10-12

**Sé a le gbà ọ́ gbọ́ pẹ̀lú àsẹ? Ẹ̀rí rẹ mbẹ nínú kí o tẹríba.**

Ẹ jẹ́ kí a lọ wọ ìtàn kan ninú Bibeli ti kò bá jẹ̀rí si àseyọrí tí o ninú ayé.

*Àwọn Filistini kó ara wọn jọ láti bá Ísráẹlì jà, ẹgbà-mẹdógún kẹ̀kẹ̀, ẹgbàta ọkùnrin ẹlẹ́sin, ènìyàn sípọ̀ bi yanrìn lẹ́tí òkun , wọ́n sì gòkè wọn dó ní Mikmasi ní ìhà ìlà oorùn Bet Afeni. Àwọn ọkùnrin Ísráẹ̀lì si ri pé wọn wà nínú ìpọnjú tí àwọn ènìyàn na wa ninu ìhámọ́. Nígbanà ni àwọn ènìyàn na fi ara wọn pamọ́ nínu ihò àti nimnú pàntí nínú àpáta, ní ibi gígá, àti ninú kànga gbígbe. Òmimràn ninú àwọn Hébérù gòkè odò Jórdánì sí ilé Gádi ati Gilgali.*

*Síbẹ̀ gbogbo ènìyàn na si nwáríri lẹ́yìn re. Ó si dúró ni ijọ́ méje, de àkókò ti Samueli dà fún un; sùgbọ́n Sámúẹli kò wá si Gílgali àwọn ènìyàn si túka kúrò ni ọ̀dọ̀ rẹ̀. Saulu sì wipé, mú ẹbọ sísun àti ẹbọ ìrẹ́pọ̀ nà fún wa"ó sì rú ẹbọ sísun na*

—1 Samuẹli 13:5-9

*"Sámúẹli sì wí fún Sáulù pé, ìwo kò hu ìwà ọlọ́gbọ́n: ìwọ kò pa òfin Olúwa Ọlọ́run rẹ mọ́; tí òn ti pa ní àṣẹ fún ọ: nítorí nísisìyí ni Olumwa ìbá fi ìdí ìjọba rẹ̀ kalẹ̀ lórí Isramẹli lailai. Sùgbọ́n nísisìyí ìjọba rẹ kì yóò dúró pẹ́:* ***__Olúwa ti wà fún ara rẹ̀ ọkùnrin ó wù u ni ọkàn rẹ̀.. Olúwa pàṣẹ fún u ki ó se olórí fún àwọn ènìyàn rẹ__****. nítorí pé ìwọ kò pa àṣẹ tí oluwa fi fun ọ mọ́"*

—1 Samueli 13:13-14

Wọn kan Saul làbùkù nitorí ti kò bọ̀wọ̀ fún àṣẹ. Lẹ́ẹ̀kansi, a tún ti rí pé tí ó kò ba le bọ̀wọ̀/tẹriba fún àṣẹ; o kò le ni àṣẹ' Mo fẹ̀ lati tọ́kasí ohun kan ti ó se pàtàkì nibiyí. Oluwa yóò sàwari ẹni bi ọkàn rẹ. Kín ni bi ọkàn rẹ̀" túmọ̀ sí"?

*"Nígbàti ó sì mu kúrò, ó gbé Dáfidì dìde ní ọba fún wọn ẹnití o sì jẹ́ri rẹ̀ pé, Mo ri Dáfidì ọmọ Jéssè ẹni bí ọkàn mi* ***__ti yóò se gbogbo ìfẹ́ mi"__***

—Ise Awon Aposteli 13:22

Báwo ni Ọlọrun ti setúmọ̀ ẹnikan ti ó ni ọkàn Rẹ̀?. Ni pàtàkì, ó jẹ́ ẹnikan ti ó kóríra ohun ti Ọlọrun kórira àti fẹ́ràn ohun tiỌlọrun fẹ́ràn, ẹnikan ti yóò se ohun ti Ọlọrun kó bá se tí ó bá wà nibẹ̀. Ni ọnà miràn, ti Ọlọrun ba kórira ẹ̀ṣẹ̀, wọn ò kórira ẹ̀ṣẹ̀. Ti Ọlọrun bá fẹ́ se nkan, wọn o ri pé ó jẹ́ siṣe. Ti ó túmọ si pé, à lérò pe ẹnikan bi ọkàn Ọlọrun ni ẹni ti o ni ẹ̀bún t'ẹ̀mi tóga. Alerò pe lati wà nítẹ̀mi ni kí a ma kọrín ìyìn ni pẹ̀lẹ́pẹ̀lẹ́. Sùgbọ́n Ọlọrun sọ ni kedere ni pé ki ó jẹ́ ẹni tó gbọràn si ìsìn tẹ̀mì.

> *Sámúẹ̀li sì wípé "Olúwa ha ní inú–dídùn sí ọrẹ sísun àti ẹbọ bí pé kí o gbóhùn Olúwa gbọ́? Kíyèsi i ìgbọ́ràn sàn ju ẹbọ lọ, <u>ìfetí sílẹ̀ sì sàn ju ọ̀rá àgbo lọ</u>. Nítorípé ìsọ̀tẹ̀ dàbí ẹ̀sẹ̀ àfọ̀sẹ àti agídí gẹ́gẹ́ bí ìwà buburú àti ìbọ̀rìsà. Nítorípé ìwọ kọ ọ̀rọ̀ Olúwa òn sì kọ̀ọ́ ní* ọba"
>
> —1Samueli 15 22-23

Lẹ́ẹ̀kansi, jẹ́ ki nsọ̀ pé ohún Ọlọrun ndún bi ohún ọ̀ga mi! Ọlọrun si ni ìdahùn rẹ si àṣẹ ni a ni latí dánwò nigbàti kò sí ẹniti ó mọ́ orúkọ́ rẹ. Ọ̀pọ̀ àwọn èniyàn ni kò ni oye bi nkan wọnyìí ti nsiṣẹ́. Wọn kò sì ri iṣẹ́ ti wọn nse bi ohun kan to lapẹrẹ:  bi nkan ti kò se pàtàki  Sùgbọ́n nkan ti wọn kò mọ̀ ni pé wọn kọ́ ara wọn lati ni ìtẹríba ni, lati wóò ni ti ara wọn bótisewà boyá nkan tí ó tọ́ latí fọ̀wọ̀ fún ni tàbi tẹríba fún ni lorí ohun ti wọ́n fẹ́ àti àfojúsùn wọn. Àwọn èniyàn kò tíì kẹ́kọ́ pé ni ìsẹ́jú ti wọn ti gbà lati ni ìgbẹ̀kẹ̀lé ninú iṣẹ́ kekeré ti wọn rọran se yìí ni wọn ti gba lati se iṣẹ́ na bi ti ara wọn, Ki ì sì se bi àwọn èniyàn ti se ma nri nkan nìyì. Nkan ti ó tóbi ni ó ma njẹ́ àfojúsọnà wọn. Niwọn ìgbati ó kú jẹ̀ isẹ́ fún igbà diẹ ni fún àfikún ni owó ni kin nse nkan nla ni. Àsìse ni!!!!

**TORÍNÀ, LẸ́Ẹ̀KANSI, JẸ́ KÍ NSỌ PÉ OHÙN ỌLỌRUN NDÙN BÍ TI Ọ̀GÁ MI!**

Kò sí nkan ti njẹ́ iṣẹ́ ti kò tó nkan tàbi se pàtakì. Kò sí ìṣẹ́ àkànse to kéré. Dafidi ni iṣẹ́ kékeré, iṣẹ́ ti kò se pàtàkí, o ntọ́jú agbo àgbutàn, Sùgbọ́ n ó se pàtàkì lojú rẹ̀. ó fi àyé rẹ̀ wewí ó kere jù bi ẹ̀meji lati dààbobo àwọn àgutàn nà Ti o túmọ si, ó ní igbẹ́kẹ̀lé ninú ohun ti à fifún un  ó sì mú iṣẹ́ rẹ̀ ni ọkúnkúndùn. Lóòtọ́ kò si ẹlomiràn ti o mọ ẹniti o jẹ́, Ọlọrun mọ̀ ọn! Ọlọrun si mọ ibiti ó wà gàn ni gbogbo àkókó.

Ọlọrun mọ ibiti ìwọ na wà bakanna, Ó si mọ ọkàn rẹ si pa ti àṣẹ. Nkan ti o wà nibẹ ni pé ti ó kò ba le tẹribá fún ènìyàn ti o le rí o kò ni lé tẹríba fún Ọlọrun, ti o kò rí. Ọ̀pọ̀lọpọ̀ awọn ti mo ti bá pàde ni wọn ni làákáyè ẹ̀tọ́ mi ni, làákàyè mo njiyà; nigbàgbogbo àsise ẹlomiràn sì ni. Nigbogbo igbà ni wọn máa nsọ pé àsise ọ̀gá ni, àsise àwọn ìjọba ni, wọn kan nse diẹ ni , wọn nsiṣẹ́ nigbati wọn bá mú wọn nitipá lati seé. Wọn ti se de ibi pé wọn kò le danurò fún ara wọn, ẹni lati sọ ohun ti wọn o se fún wọn ni, Bi ọ̀rọ̀ àwọn ọmọ Israẹli ti ri niyìí, Tí wọn ti jade kurò ni oko ẹrú ni ọ̀pọ̀ ọdún, ti wọn tún ronú bi ẹrú, nigbà ti wọn ti di òminira tan. Làákàyè ti ẹrú ti wọn ti ní kò le siṣẹ́ nigba ti wọn ti nkojú àwọn òmìrán ílẹ̀ nà. Ọlọrun ni lat kọ́ wọn fún àseyọrí ki wọn to lọ si ilẹ̀ nà. Ó ni lati kọ́ ọ sáájú kí o tó lọ si ilẹ̀ nà. Ilẹ̀ ti mo nsọ̀rọ̀ nipa rẹ̀ ni àyànmọ/kadàrá rẹ. Se ó wá kó wọn?

> *Ó sì rẹ ọ́ sílẹ̀, ó si fi ebi pa ọ́, ó si fi mánnà bọ́ ọ, tí ìwọ kò mọ̀ bẹ́ni àwọn baba rẹ kò mọ̀; kí o le mú ọ mọ̀ pé ènìyàn kò tí ipa ounjẹ nìkan wà láyé, bíkòse nimpa gbogbo ọ̀rọ̀ tó ó ti ẹnu Olúwa jáde ni ènìyàn wà láye"*
>
> —Deutaronomi 8:3

> *Ẹnití o fi mánnà bọ́ ọ ní aginjù, tí àwọn baba rẹ̀ kò mọ ri;* ***kí ó le rẹ̀ ọ sílẹ, kí o le dán wò. láti se ọ ní ọ̀rẹ́ nígbẹ̀hìn rẹ̀'***
>
> —Deutaronomi 8:16

Ọlọrun rẹ̀ wọ́n sílẹ̀, tumọ sí pé ó mu wọn di alaìnito ti ò nilò oluranlọwọ. . Wọn ni latí kọ́ bi a ti ngbarale Ọlọrun laise ara wọn. Nitori ogun nla wà niwaju wọn ju ki a ma wá ounjẹ ti a o jẹ̀ lọ. Awọn ọmiran àti olódi ilú si wà ni wajú ti wọn jáláyà ni waju à yàfi ti wọn ba rí Ọlọrun ni titóbi to ju gbogbo isóro wọn lọ.

Ẹlẹkeji, wọn tún lati kọ bi a ti nyan ohun tí ó tọ́ fúnra wọn laísí pé wọn ró wọn lati se bẹ́ẹ̀. Loniì, mo ti ri àwọn obi ti wọn gbìyànjuú lati kọ́ isesí àwọn ọmọ wọn dipò ki wọn kọ́ ọkan wọn. Ki wọn sọ fún ọmọ pé ki o lọ tún yàra wọn se, o wa sọ ilẹ̀kún yàrá gbọ̀n bi kí o já, pẹ̀lú ìwa ìsọtẹ̀ àti àìsí ibọ̀wọ̀ fún àti ìtẹ́ríba. Òbi ti ó fẹ́ ba ọmọ rẹ sọ̀rẹ́ yóò wọle àti rí pé yara ọmọ rẹ̀ mọ yóò wa ki ọmọ nà pé o ti se isẹ́ nla. Kò dára tó, asise ni.

Ọmọ ni lati gba latí òde ni, ki ise lati inú. Ki ènìyàn ni ìtẹriba ó jẹ̀ ise ti ọkan. Nigbàmíràn, àwọn òbí kò ni sí ni sí nibẹ̀ lati sọ pé ohun ti wàá se nìyìí. Ti àwọn òbí ba ti yọwọ wọn kúrò, ọmọ yóò bẹ̀rẹ̀ si ni se nkan to bá wù ú. Nkan ti ó ti wà ninú ọkan ọmọ na ni yóò wa ma farahàn. Nibiyìí ni ọ̀pọ̀ obí ti má n ma ri ọmọ wọn ninú wàhálà àti ìdaàmú, ti wọn ó wa máa sọ pé ọmọ dáadáa ni Johnny, kóda ìyalẹnu ni ó jẹ́ fún awọn pẹ̀lú iru ìwà tí o hù nigbà ti o pari ni ile ẹ̀kọ́ giga tàbi ti ó wa ni ti ara rẹ̀.

Bibeli ni òun yóò dán Israẹli wò ki o ba le dara fún ni opin ohun gbogbo. Nkan ti à nsọ gan nìyìí. Kò dàbi àwọn òbí ti wọn fẹ́ ki àwọn ọmọ fẹ́ràn wọ́n nikan lo jẹ wọn logún, Ohun ti ó jẹ́ Ọlọrun lógún ni bi ọmọ náà yòó se wa dáadáa àti fún itọjú ìgbà pípẹ́. Yóò ti satúnse ọkàn àti ìwà wọn ki wọn tó ya onibàjẹ́ ninú àwọn ìwà wọn. Nkan ti ó túmọ si nìyìí nigbàtí Ọlọrún sọ pe Òn o dán wọn wò. Ọlọrun yóò le mú ki wọn le satúnse bi ìwà àti ìse ọkàn wọn se nfarahàn nigbàti wọn ba bèrè pú ki wọn nitẹriba.

Gbogbo ènìyàn ni o ni lati la ìdànwò ìtẹriba/ ìbọ̀wọ̀ fún ni kọja! Torínà, nibo ni Ọlọrun ti nkọ́ wa lóde onií nigbàti kò sí asálẹ̀ ọ̀ si àgbélébu? Nibo ni a ti le gbọ́ ohùn rẹ̀ ti a o fi kọ́ ìtẹríba/ìbọ̀wọ̀ fún ti a ó fi yege fún ìgbéga wa tó kàn? Ránti ohun ti Ọlọrun sọ nipa Saulu? Ìgbọ́ràn sàn ju ẹbọ rúrú lọ. Bi o tí nyin Ọlọrun ninú ìjọ ki se ìpìlẹ̀ igbéga rẹ to kàn. Se Ọlọrun le ni ìgbẹ́kẹ̀lé ninú rẹ pẹ̀lú àṣẹ? Nibò ni èyìí yóò ti bẹ̀rẹ̀? Ninú ilé.

> *Ẹ̀yin ọmọ ẹma gbọ́ ti àwọn òbí yín nínú Olúwa: nítoripé ẹ̀yíni ó tọ́, Bọ̀wọ̀ fún ìyá àti baba rẹ èyí ti ise ọ̀fin ìkínni pẹ̀lú ìlérí. Kí o le dára fún ọ, ati kí ìwo ki o le wà pẹ́ ní ayé"*
>
> —Efesu 6:1-3

Kílódé tí o fi jẹ́ pé bi o bá gbọràn si àwọn òbi rẹ̀ o le mú ọ ni ẹ̀mi gigùn àti kí o sì tún dara fún ọ? Se Ọlọrun wá fún ọ ni àwọn kókó fún ìgbọràn ni? Rárá, sùgbọ́n ti ó ba kó lati mà bọ̀wọ̀ ati ni ìtẹríba fún àwọn òbi rẹ, àwọn àṣẹ ti o wà lorí ayé rẹ,nigbànà ni wa bọ̀wọ̀ àti fí ọlá fún Ọlọrun. Ti o ba bọ̀wọ̀ fún àṣẹ Ọlọrun ninú ayé rẹ,wàá gbọ́ràn gbogbo nkan yóò ma lọ dáradára fún ọ. Ma wà sọ wipé ohùn Ọlọrun ndún bi ti àwọn òbí rẹ

nigbati o wà lọmọde ni àbẹ́ ìtọ́jú wọn.

Ọ̀nà kejì ti Ọlọrun tún fẹ̀ gbà kọ́ ọ bi wa ti se má bọ̀wọ̀ fún àṣẹ ni fifi ọ́ si àbẹ́ awọn àṣẹ ti ènìyàn. Ọ̀ga rẹ, Pasítọ̀, Agbófínró Ọlọpa, àti ìjọba gbogbo wọnyìí ni àpẹẹrẹ ti Ọlọrun ti sọ fún wa lati ma tẹriba.

Mo ràntí àwọn idilé kan ninú ìjọ wa ti wọn ma fi gbogbo ìgbà se àròye àti ma sọ̀rọ̀ lórí àwọn ìsòro. Kódà wọn ti fẹ́ pàdánu ilé wọn bayìí wọn si nilò ẹgbẹ̀rún mẹ́wa dolla  lati yanjú ohun ti o wà nilẹ̀ àti  lati yàgò fún gbigba ile nà lọ́wọ́ wọ̀n. Wọn ó ti sọ ìtàn àyé wọn fún ìgbà ènìyàn ninú ìjọ. Lakótán, àwọn ìdile kan pinnu lati ràn wọ́n lọ́wọ́  wọ́n si fún wọnẹgbẹ̀rún mewa dolla.Sùgbọ́n katówí kátófọ̀ ni àrin bí ose melo kan wọn tùn ti padà sí ipò ti wọn wà tẹ́lẹ̀ wọn si padánù le nà. Mo ti ba àwọn tọkọtaya yi sọ̀rọ̀, ti àwọn mejeji kò ri isẹ́ se nipa ipò ti wọn wà. Mo gbà wọn niyànjú pé ki wọn kàn wá nkan se na tití wọn ó fi ri iṣẹ́ ti wọn fẹ́. Wọn le siṣẹ́ ni bi ile ìta ounjẹ ni ibi gbogbo ninú ìlú, sùgbọ́n wọn kì se iru iṣẹ́ ti àwọn fẹ́ niyìí. Mo ri kedere pé ki ise àini owó lọ́wọ̀ ni ìsoro wọn, bikòsepé àini òyé àṣẹ ati ti òjúse. Fún àwọn ìdi kan, wọ́n kùna lati ri pé  àwọn ni ojúse lati lo àṣẹ lorí ayé ara wọn àti se ohun ti o ban á wọn lati fi yanjú gbogbo ìsòro náà.

Rick Renner, ọ̀rẹ́ mi kan, pé ki òun tó bẹ ẹnikẹ́ni lọwẹ̀, òun o bèrè lati rí ọkọ̀ ayọkẹ́lẹ́ wọn tàbi nkankan  ti yó gbe sile wọn lai sọ. Ó ni ìwòyé pé ẹniti kó le se ojúse rẹ̀ lorí nkan ti nse tirẹ̀, ọkọ̀ rẹ̀,wọn kò ni le se ojúse lorí nkan tirẹ̀. Óni kò nipẹ́ ti wọn o fi sọ ọ̀fisi òun dà bi ọkọ̀ wọn ti rí.

Mo fojú inú wo ìgbà ti mò nla aginjù ayé kọjá lọ́wọ́ yìí ti mo ngbà ìdánilẹ́kọ. Mo wá láyọ̀ pé Ọlọrun kò jẹ́ ki nfi ìwà àìnání sẹ̀ sí àṣẹ. Ó rẹ̀mí sílẹ̀ ati dánmiwò ki  nbá le gbáradì fún  iṣẹ́-sísé ti o yàn mi fún.

Mo si ranti ìgbàti kò si owó rárá ti nkan le nigbàti a wà ni ahéré ti a ngbé nigbànà. Pẹ̀lu ọ̀pẹ̀ ni, mo ti ti ile isẹ́ ìdókòwò nlá kan pa rí ki nba le san gbogbo gbèsè to ti npẹ́ to wà nilẹ̀, sùgbọn mi o tètè ri sọ̀wédowó gbà ni kíákíá, mo wa lérò pe ma lọ si ilé ìfowọ́pamọ́ lọ fún sisàyẹ̀wò àkọọ́lẹ̀ ti ki se ile ífowopamọ mi, ma wa kọ àwọn sowedowò ti o ti di gbèse yí si banki mi lati bẹ̀, mo lerò wipe máa rìgbà ni ọjọ keji kin le sán lati fi bo àsiri àwọn gbèsè tilẹ̀ ni ile ìfowópamọ tuntun. sùgbọ́n kò jade fùn bi ọ̀sẹ̀ mejì; Ni ojojúmọ ni mo wá nkọ sọ̀wedowò ti kò ni owó ninú lọ si banki mi kan  ki sowedowó yi tó dọwọ wọn. Ọsẹ̀ meji ni mo fi se, ti àwọn

sowedowó yí tún fi di ẹgberún meji dolla, níwọ̀n ìgbàti mo gbọdọ̀ wa àwọn ounjẹ kan.Ni àsikò gan,àwọn o owó na wá npọ̀si ni.

Sùgbọ́n gbogbo rẹ̀ dopin ni òwúrọ̀ ọjọ́ ti ọ̀gà banki pé mi, Ọ́rọ́ ti ó kọ́ sọ ni pe" Ọgbẹ́ni Keesee, mo mọ ohun ti ò nse, mo si ma fa igi le gbogbo ìwe rẹ lonií. O sí gbọdọ̀ mú owó wa lati fi yanjú  gbogbo gbèsè rẹ, o kò sì ni ri ànfàni lati wa fi owó pamọ́ si banki yìí mọ́.  Wọ́n gbá mi mú; Nkan ti o wa burújù ninú gbogbo ohun ti ó sẹlẹ̀ yìí ni pe sọwedowó ti mó nlò ni a ti kọ́ ẹṣẹ ìwe mimọ́ sí. Mo si ti ma njẹ́rí fún ọ̀gá Banki yìí bi Ọlọrun ti tóbi tó. Mo dupẹ́ pé sọ̀wedowò ti mo nrétí dé ni ọjọ́ nà, mo si lọ lati lọ yanjú gbogbo gbèsè nà ni ọjọ nà. Sugbọ́n mo ni lati lọ bá ọ̀gá banki nà ninú ọfisì rẹ̀, lati lọ fún ìronúpìwàdà niwájú rẹ̀, mo wa sọ fún wipé ki ó ma ba Ọlọrun wi o pé èmi ni mo fa gbogbo ohun ti ó sẹlẹ̀, ó si jẹ́ ìwa omùgọ̀.

Ọdún àkọ́kọ́ mi si niyìí ninú isẹ́ oko-owò ti mo nse ti mo si wà lábẹ́ igbákeji-Ààrẹ ni ẹkùn ti o nkọ mi niṣẹ́.  Bi o ti se nyẹ ọkan ninú àwọn ọjà ti mo ti tà wò, o sakiyèsí pé àye ìfọwọ́si kan sófo.Óni,  "Kò si ìyọnu , mu dani ki o sì ri wipé o wa ibi ti o yẹ ki o wa ki o si se àtunse. Lẹ́yìn gbogbo rẹ̀," óni,  pé  àwọn fẹ́ ọjà na o si ti fọwọ si gbogbo ibi ti ó yẹ' Nkan tí o se nìyìí. Lẹ́hìn bi osù kan, mo gba ìpè kan lat ọ̀dọ̀ àwọn aláṣẹ́ pe onibara mi kan pè mi lẹ́jọ́ ọ̀kẹ́ marún dọ́llà nitori ti mo gbàgbe lati kọ orúkọ rẹ̀ si ìwe ti a fi ngba owó ni banki. Wọn din owo nà kù sí ẹgbẹ̀rún márún dọ́llà nitorí ti o kan Ààrẹ ẹkùn mi na, o ni àwọn ojúse ti ó yẹ ki o se ninu ọ̀rọ̀ na, wọn si da mi dúrò lẹnu ìsẹ́ nà.

Sùgbọ́n mo ni lati kọ́ ẹ̀kọ́! Ọkan lara àwọn osìsẹ́ mi ti mo sẹ̀sẹ̀ gbà nilò lati se ìdánwò ti àdojútófò, kò wa ni owo lati ra iwe ti yóò ka, mo wa se ẹdà kan fún un lati lò. O si fi silẹ̀ ni ibi ti o ti lọ se idanwo nà, mo wa gba ìpè miràn lati ọ̀dọ̀ àwọn àlàsẹ ti ó npè mi lẹ́jọ́ fun ẹ̀dà iwe ítẹ̀. Ni ayé ìgbàyẹn mo mọ ọ̀nà ti ó lọ́ si ilé isẹ́ IRS bí ẹ̀yìn ọwọ́ mi ni.  Gbobo ìgbà ni mi ò kí tètè sam owó ori mi ti o si ni ìtanràn ninú. Mo wá bojú wẹ̀yìn pẹ̀lú ohun gbogbo ti o ti dàpọ̀ mọ ara wọn yìí. Ọlọrun ti npalẹ̀ mi mọ fún un, ó nkọ mi. Ó ti mọ pé ni ọjọkàn ma ni Milliọnù dọlla, ko si ni gbà ki nfi ohun kan silẹ̀. Mo dupẹ lọ́wọ́ Ọlọrun.

Mo ni lati kọ́ pé Ọlọrun ni Olùgbẹ̀kẹ̀lé mi ati pé Ọlọrun kì í gbé ni ga lorí iṣẹ́ siṣe nìkan. Ó ti dán bi mo ti se jẹ́ olóòtọ́ si wò bakannà. ìdí sì niyìí ti mo se sọ pé ohùn Ọlọrun Ndún bi ti ọ̀gá mi. Ọ̀ga rẹ ni àwọn ohun èlò ti

Ọlọrun nlò lati kọ́ ọ lẹ́ẹ̀kọ́ fún ise àkànse miràn ti o tún mbọ̀ lati mú ọ tẹríba. Se wa sì yege ninú ìdanwo náà?

> *Nítorí́ tí ìgbéga kò ti ìlà-oorùn wá, tàbì ní ìwọ̀-oorùn, ki íse làti gúusù wá. Sùgbọ́n Ọlọrun ni onídájọ́:ó sọ ọ̀kan kale, ó gbé ẹlòmíràn lékè.*
>
> —Orin Dafidi 75:6-7

> *Gbogbo ìbáwí kò dàbí ohun ayò nísisiyí, bíkòse ìbànújẹ́: sùgbọ́n níkẹhìn a so èso àláafíà fún àwọn tí a ti tọ́ nípa rẹ àni èso òdodo tí mó fẹ́ se tẹ́lè bí.*
>
> —Hébérù 12:11

> *Ẹ̀yin ọmọ-ọ̀dọ̀, ẹ má gbọ́ ti àwọn olúwa yín nípa ti ara, pẹ̀lú ìbẹ̀rù àti ìwárìrì ní òtítọ́ ọkàn yín, bí ẹni pé sí Kristi. Kì íse ti àrojúse bí àwọn tí ńwu ènìyàn; sùgbọn gẹ́gẹ́ bí àwọn èrù Kristi, ẹ má se ẹ ma se ìfẹ́ Ọlọrun lati inú wá, E má fi inú rere sin bi sí Olúwa, ki isi ise si ènìyàn. Bí ẹ̀yin ti mọ̀ pé ohun rerekóhunrere tí olúkulukù bá sẹ, on na ni yóò sì gba padà lọ́dọ̀ Oluwa, ìba se ẹrú tàbí òmìnira. Àti yín oluwa,e máase ohun kanna si wọn, e. maá din iberu yin ku;bi ẹ̀yin ti mọ̀ pé Olúwa ẹ̀yin tìkarayín si mbẹ nim òrun; kò sìsí ojúsajú ènìyàn lọ́dọ̀ rè.*
>
> —Éfésù 6:5-9

Ìgbọ́ràn àti ìbẹ̀rù àtí ìwárìrì!. Wọ̀nyìí ni ìwa ti ó yẹ ki o nì si ọ̀ga rẹ. Ìgbọràn rẹ si ọ̀ga ni Paulu túmọ̀ si sise ìfẹ́ ti Ọlọrun. Ìyàlẹnu? lo jẹ́!

Torínà kinni ohùn Ọlọrun ti se ndún ? Ọ̀ga rẹ!

## ÌDÁNWÒ NI!

Bi mo ti nmú ẹ̀kọ́ yìí wá si ìpari, Mo ni ìgbẹ́kẹ̀lé pé o tí ni àtilẹ̀yin àti ìwúrí. Ẹ̀mi Mimọ́ jẹ́ àlábásiṣẹ́pọ̀ tó yanilẹnu ni tòótọ́ lati ni ninú ayé, Ẹniti o ti sèlérí pé On kò ni fi ọ́ silẹ̀ kò sì ní kọ̀ ọ́.. Ó jẹ́ iyì nla lati pin àwọn ótítọ́ ti o se iyebíye yìí pẹ̀lú rẹ.

—Gary Keesee

Fún àwọn àlàyé lẹkúnrẹ́rẹ́ bi o ti se le bọ́ lóko gbèsè àti bí o ti se le bẹ̀rẹ̀ ìdóko-owò lailewu, o le kàn si ile ìsẹ́ wa, Forward Financial Group.

Fún àwọn àlàyé nipa Ìjọba Ọlọrun, jọ̀wọ́ lọ si FaithLifeNow.com.

Fún awọn àlàyé tóníse pẹ̀lú Faith Life Church, ó le lọ sí FaithLifeChurch.org .

ORI KEJÌLÁ

# BÍ A TI SE LE GBÀDÚRÀ ÀTI GBA ÌRÌBỌMI TI ẸMI MIMỌ́

Ohungbogbo ti a bá gbà lati ọ̀dọ̀ Ọlọrun à gbà á pẹ̀lú ìgbàgbọ́ ni ninú ohun ti Ọlọrun ti sọ fún wa, àti bí a ti se ngba àwọn ẹ̀bùn wọnyìí lati ọ̀dọ́ Ọlọrun ni ó yàtọ̀. Ki o tó gbàdúrà àti ri gbà, ríi dájú pé o ka ìwe mimọ́ ti à kọsílẹ̀ ninú ìwe yìítítí wa fi rí àridájú pé ìfẹ́ Ọlọrun ni fún ọ àti pé ati dáhùn àwọn ìbérè rẹ. Ní wọ̀n ìgbà tí o bá ti ni àrídáju pé o ti gba ìrìbọmi ti Ẹ̀mi Mimọ́ o sì wà ninú rẹ, nigbànáà kan gbàdúrà yìí:

> **"Bàbá, mo bèrè fún ìrìbọmi agbára ti Ẹ̀mi rẹ lónìí. Mo gba NÍSÌSÌYÌÍ, gégé bí ọ̀rọ̀ rẹ, pẹ̀lú agbára látì nínú Ẹ̀mí. Mo bèrè èyí ní orúkọ Jésù àti fún ògo Rẹ̀! Amin."**

Ò nwá ki o ní àwọn ìrírí kan, tàbi ìmọ̀ara kàn, sùgbọ́n o dúró sinsin lorí ọ̀rọ̀ Ọlọrun, gbàgbọ́ pé o ti rigbà nigbàti o ba gbàdúrà. Lẹ́hìn ìgbà ti o ti bèrè ti o sì ti rígbà, bẹ̀rẹ̀ si ni máa yin Ọlọrun àti ma dupẹ̀ lọ́wọ́ Rẹ̀ fún ìfòróróyàn pẹ̀lú Ẹ̀mi Rẹ̀ gẹ́gẹ́ bi o ti sèlérí.

Nigbatí o bá gbàdúrà, kan mọ dajú pé oní oye pé *o rí gbà nígbàtí o bá nbèrè*, kì ise nigbati o ti fi ẹ̀rí hàn pé o ti rígbà. Ẹ̀rí rẹ ni Ọ̀rọ̀ Ọlọrun.

*"Ohunkóhun tí ẹ̀yín bá tọrọ nígbàtí ẹ ba ńgbàdúrà, ẹ gbàgbọ́ pé ẹ ti rí wọn gbàná, yóò sì rí bẹ̀ fun yín"* (Máákù 11:24b)

Rí dajú pé ò nlo àsikò lati máa jọsin si Oluwa nigbàti o ba ti

ngbàdúrà ti Ẹ̀mi Ọlọrun si ni ominira lati fi ara rẹ̀ hàn ninú èdè àdúrà rẹ. Ọlọrun kọ̀ ni yóò muú kí ẹnu rẹ máa mi,! O ni lati si ọkàn rẹ payá lati gbàdúrà ninú Ẹ̀mi. Nigbàgbogbo, àwọn èǹiyàn máa ni ìyè ara ti itanijí, tabi ki ọ̀na ọ̀fun há, nigbàti wọn bá ngbàdúrà tàbí ni ìmọ̀ara ti Ẹ̀mi Ọlọrun.

Bi o ti jọsìn fún Ọlọrun fi ara rẹ silẹ̀ fún Ẹ̀mi Ọlọrun. Wa si bẹ̀rẹ̀ sí ni máa ìmọ̀ orisirisi àwọn ohùn tàbi àwọn èdè kan ti o njade wá lati inú ẹ̀mi rẹ. O ni lati fi ara rẹ fún àwọn ohùn yìí nipa ìgbàgbọ́. Bi o tin se èyí ni wa máa sàn lọ àti tú jade ninú ẹ̀mi Ọlọrun ti o npọ̀si.

Ti o bá jẹ́ pé àwọn idi kan wà ti o kò fi fèdèfọ̀ ni keté ti o bẹ̀rẹ̀ àdúrà, má yọ ara rẹ lẹ́nu npa rẹ̀. Wa ri gbà nipa *ìgbàgbọ́* bẹ́ sì ni ki o tẹ̀síwájú lati má dupẹ́ lọ́wọ́ Ọlọrun fún ìfòróró yàn Rẹ̀. Mo ti ri àwọn èniyàn ti wọn lọ si ìpade inú ìjọ,lẹ́hìn ti wọn ti gbàdúrà fún ìríbọmi ti Ẹ̀mi Mimọ́ tán ti wọn si bẹ̀rẹ̀ si ni fèdèfọ̀ ni ọ̀nà nigbàti wọn nlọ sí le wọn, ni inú ilewẹ̀ ni òwurọ̀ tàbi nigbàti o nroko àyiká ilé lẹ́yín bi ọjọ́ melò kan. Kọ́kọ́rọ́ rẹ̀ ni lati rí gbàa nipa ìgbàgbọ́ ki ise nipa ìmọ̀ara.

Jẹ́ ki àdura gbigbà ninú ẹ̀mi jẹ́ ise rẹ ni ojojúmọ aye rẹ ki o si ma gbàdurà dáadáa ninú ẹ̀mi. Ọlọrun yóò ba ọ sọ̀rọ̀ yóò si ma darí pẹ̀lú ìdáhùn ninú ohungbogbo ti nse tìrẹ. Mo nigbàgbọ́ pé wa si wà àyè lati gbàdúrà ninú ẹ̀mi àti gbàdùn gbogbo àwọn ànfani ti ìjọba Ọlọrun ti o ti jẹ́ tì rẹ tẹ́lẹ̀!

# ÀWỌN ÀKÍYÈSÍ

1. Jared Dublin "Ju fan sọ́gbà ẹ̀wọ̀n pe NFL lẹ́jọ́ fún $88 billiọnu lorí Dez Bryant non-catch Vs Packer, " wa ninú osú Kínní ọdún 23, 2015. https://www.cbssports.com/nfl/news/jailed-fan-suing-nfl-for-88-billion-over-dez-bryant-non-catch-vs-packers/.

2. http://www.dictionary.reference.com/browse/Edified?s=t.

3. Lin Edwards, "Àwọn àkọṣẹ́mọṣẹ́ nipa èrò ọkàn sọ wipé àwọn ọmọde mọ ọ̀tún sọsì , mọ ohun ti o dara si aìda ti wọn ba ti tó bi ọmọ osù mẹ́fà" Èbìbí 10, 2010, https://medicalxpress.com/news/2010-05-psychologists-babies-wrong-months.html.

Lọ sí **FLNfree.com**
láti gba àgbàsílẹ̀ àwọn ìdánilẹ́kọ̀
yìí lọ́fẹ̀ẹ́ ní èdè abínibí rẹ!

Tí o bá fẹ́ ìdánilẹ́kọ̀ sí i LỌ́FẸ̀Ẹ́ ní èdè abínibí rẹ
lọ sí **FLNfree.com**

# YÍYÍ ÈTÒ ÌSÚNÁ RẸ PADÀ
## Agbára ti Ìlànà

Ilé ayé kún fuń ọ̀pọ̀ àwọn ìpinnu tí ó se pàtàkì

*Báwo ni o ti se le mọ irú ilé tí o yẹ kí o rà, tani o yẹ kí o fẹ́, tàbí irú isẹ́ wo ni o yẹ kí o gbà?*

Tí o bá máa se àseyọrí láyé, o nílò àwọn ète ìlànà yìí..Báwo ni o ti se le mọ à wọn ìlànà náà. Nígbàtí kì íse pé ó ti nim gbogbo àwọn ìdáhùn dání?

Àwọn ohun ìjìnlẹ tí Olorun ni a fi pamọ́ fún ọ. Kì íse láti ọ̀dọ̀ rẹ wa.

**Ọlọrun fẹ́ kí o ní gbogbo àwọn ìdáhùn tí o nílò ní ìkáwọ́ rẹ-ìdí sì nìyìí tí o fi fi àwọn ohun ìjà ibi ìkọ̀kọ̀ fún ọ.**

Nínú ẹlẹ́ẹ̀kẹta irú rẹ̀ ti ìwé ètò yíyí ìsúná rẹ padà tí ó wà ní sísẹ̀ntẹ̀lé Gary Keesee se àfihàn ẹ̀yà ọkàn bí o ti se Pàtàkì nínú àwọn àseyọrí rẹ àti ìse PÀTÀKÌ ohun ìjìnlẹ̀ tí ìjọba Ọlọrun. *Agbára ìlànà!* Ẹnikẹ́ni ni ó le pẹja tí wọ́n bá ti mọ ibiti wọ́n o ju àwọn si. Ọlọrun ní àwọn ìdáhùn tí o nílò lọ́wọ́, sùgbọ́n ó ni lati ni òye bí o ti se gbọ́ àwọn ìdáhùn àti bí wa ti se lòó nínú ayé rẹ—ohun gbogbo ti ìwé ọwọ rẹ yìí wà fún nìyìí.

Darapọ̀ mọ́ Gary nínú ìrìn–àjò yìí, kí o sì sàwárí bí o ti se lo *Agbára Ète Ìlànà* yìí nínú ayé rẹ!



Gary Keese jẹ́ òǹkọ̀wé, sọ̀rọ̀ sọ̀rọ̀, olóko-òwò, onímọ̀ nínú ètò ìṣúná, àti olùṣọ́-àgùntàn ẹni tí ó ní ìtara fún rírán àwọn ènìyàn lọ́wọ́ láti borí ní ìgbé ayé wọn, paapaa julo nipa ti igbagbo, idile ati eto isuna. Gari ati iyawo re, Drenda, ti ṣẹ̀dá ọ̀pọ̀lọpọ̀ àwọn oko òwò, àwọn sì jùmọ̀ jẹ́ olùdásílẹ̀ ti Ìgbé-ayé Ìgbàgbọ́ Ní Báyìí, èyí tí ó jẹ́ àbájáde ètò tẹlifíṣọn méjì- *Yíyanjú Ètò Tó Jẹmọ́ Owó* àti *Drenda*, àpérò kárí-ayé, àti ìpèsè akọ́nimọ̀ọ̀ṣe. Àwọn tọkọ taya Keesee tún jẹ́ oluṣọ́-àgùntàn Ìjọ Faith Life nítòsí Columbus, Ohio.

P. O. Box 779, New ALBANY, OH 43054, USA
garykeesee.com